| ìlẹ̀kùn aláràbarà | *door with design* |
| iná ìlẹ́tíríìkì | *electric light* |
| máàpù àgbáyé | *world map* |

## Verbs

| | |
|---|---|
| túwò, yẹ̀wò | *to examine, to check* |
| yangàn | *boast of* |

## Verb Phrases

| | |
|---|---|
| gba ìṣirò | *get maths right* |
| mú ìwé ìṣiròo yín jáde | *bring out your math books* |
| ṣe ìṣirò kìíní | *solve the first math problem* |
| tó tèlé ìyẹn | *that follows (that one)* |

## Interrogatives

| | |
|---|---|
| ṣé .....gba ìṣiròo rẹ̀? | *did ….get the math problem right?* |
| ṣé …… gbà á? | *did ….. get it right?* |

## Other Expressions

| | |
|---|---|
| ẹ dákẹ́ ariwo | *(You all) be quiet* |
| ẹ ṣí ìwé yín sí ojú-ìwé | *open your books to* |
| o gba ... rẹ ṣámúṣámú | you got your ... *exactly right* |
| ojú-ìwé karùnúnlélọ́gbọ̀n | *page 35* |
| o káre! | *good job* |
| ó ku ẹ̀ẹ̀sànán | *nine is left* |
| ó yẹ kí á tun ìṣiròo wa wò | *we need to review our math* |
| ọ̀la ni ojọ́ ìdánwò | *tomorrow is exam day* |
| yọ ..............nínú | *take………..away from* |

 CC – 2012 The University of Texas at Austin

# Lesson 1 - Ẹ̀kọ́ Kìíní

## Possessive Pronouns

| Singular | | | Plural | | |
|---|---|---|---|---|---|
| 1st pers. | mi | *my* | 1st pers. | Wa | *our* |
| 2nd pers. | rẹ/ẹ | *your* | 2nd pers. | Yín | *your* |
| 3rd pers. | rẹ̀/ẹ̀ | *hers, his, its* | 3rd pers. | Wọn | *their* |

| | |
|---|---|
| ìwéè mi | *my book* |
| ilée wọn | *their house* |
| ojúu wa | *our eyes* |
| ìyàwóò rẹ̀ | *his wife* |
| ìwàa yín | *your (sg./pl.) behavior* |
| màmáà rẹ | *your (sg.) mother* |

**Wọn** and **yín** can also be used as pronouns of respect. Status, apart from old age, demands respect in Yorùbá society. These pronouns are, therefore, used for people like doctors, judges, professors, one's boss, one's father, mother, uncle, or aunt, etc. For example, when you want to ask someone a professor's name, i.e. 'What is his/her name?' You say 'kí ni orúkọọ **wọn**?' If the Professor's name is Àlàdé), you respond: Orúkọọ **wọn** ni Ọ̀jọ̀gbọ́n Àlàdé (His/her name is Professor Àlàdé).

Recall the emphatic pronouns below that you learned in Chapter 1 lesson 3, and compare them to the possessive pronouns above:

## Emphatic Pronouns

| Singular | | | Plural | | |
|---|---|---|---|---|---|
| 1st pers. | èmi | *I* | 1st pers. | Àwa | *we* |
| 2nd pers. | ìwọ | *you* | 2nd pers. | ẹ̀yin | *you* |
| 3rd pers. | òun | *she, he, it* | 3rd pers. | àwọn | *they* |

To form the possessive pronouns, the vowels at the beginning of the subject pronouns drop in the 1st person singular **èmi**, 1st person plural **àwa**, and in the 3rd person plural **àwọn**.

 CC – 2012 The University of Texas at Austin

## Iṣẹ́ Ṣíṣe 1

Fi arọ́pò orúkọ ìní rọ́pò ọ̀rọ̀ tí a kọ gòdògbò.
*Replace the words in bold with possessive pronouns.*

**Bí àpẹẹrẹ:**

Orúkọ **èmi àti Túnde**.

Orúkọọ wa.

1. Bàbá **ìwọ àti Kẹ́mi**. (in conversational context)

   ______________________________

2. Ìwé **ìwọ** (not in conversational context).

   ______________________________

3. Ilé-ìwé **Àìná**.

   ______________________________

4. Ilée **bàbá àti màmáà mi**.

   ______________________________

5. Ìwé **èmi àti ìwọ**.

   ______________________________

 CC – 2012 The University of Texas at Austin

## Iṣẹ́ Ṣíṣe 2

Lo arọ́pò orúkọ ìní tó tọ̀nà.
*Use a possessive pronoun.*

**Bí àpẹẹrẹ:**

Bàbáa Túndé = Bàbáa rẹ̀

1. Bàbá àti mámáa Títí
2. Ẹ̀gbọ́nọn Jídé
3. Àbúròo Títí àti Wálé
4. Àbúròo bàbáa Wálé
5. Màmá èmi àti ìwọ
6. Ìwé ìwọ (conversational context)
7. Pẹ́ńsùlù ẹ̀yin (not in conversational context)
8. Kíláàsì àwa àti ẹ̀yin
9. Ìwée Jídé àti Títí
10. Bébà ìwọ (conversational context)

 CC – 2012 The University of Texas at Austin

### Iṣẹ́ Ṣíṣe 3

Dí àwọn àlàfo wọ̀nyí pẹ̀lú àwọn ọ̀rọ̀ tí wọ́n bá wọn mu. Rí wí pé àwọn ọ̀rọ̀ náà ṣe déédé pẹ̀lú àwọn olùwà inú gbólóhùn náà.

*Use a possessive pronoun to fill in the space below. Let the pronoun correspond to the subject of the sentence or phrase.*

1. Olú fẹ́rànan bàbáa ________________, ṣùgbọ́n kò fẹ́ràn ìyáa __________________.
2. Èmí fẹ́rànan olùkọ́ọ̀ _________________,ṣùgbọ́n Adé kò fẹ́ràn olùkọ́ọ ____________.
3. Ó fẹ́ràn ajáa ______________________ , èmi fẹ́ràn ológbò ______________________.
4. Àwọn òbí Olú fẹ́ràn àwọn ọmọọ ____________,ṣùgbọ́n wọn kò fẹ́ràn ìdọ̀tí nínú ilée ____________________________.
5. O fẹ́ràn ajáa ______________________, ṣùgbọ́n Olú kò fẹ́ràn iṣẹ́ẹ ______________.

 CC – 2012 The University of Texas at Austin

# Lesson 2 - Ẹ̀kọ́ Kejì

## The Plural marker 'àwọn'

'Àwọn' is a plural marker that is placed before the noun. For example:

| | |
|---|---|
| 1. Mo ri àwọn obìnrin náà lánàá | *I saw the women yesterday* |
| 2. Àwọn ilé nàá ń jó. | *The houses are burning* |
| 3. Àwọn ọkùnrin máa ń dé fìlà | *Men do wear hats* |

**Compare:**

| | |
|---|---|
| 1b. Mo ri obìnrin náà lánàá | *I saw the woman yesterday* |
| 2b. Ilé nàá ń jó. | *The house is burning.* |

However, the use of **àwọn is** sometimes redundant and therefore does not necessarily have to be used. For example:

| | |
|---|---|
| 4. Obìnrin kì í dé fìlà | *Women do not wear hats* |
| 5. Ọmọdé kì í sùn | *Children don't sleep* |

In 4 and 5, the subjects do not have to be preceded by **'àwọn'** to indicate plurality.

We should, however note that **àwọn** can be singular when used honorifically--as a mark of respect as for example ' **àwọn bàbáà mi** ní kí n kí i yín ' *my father asked me to say 'hi' to you.*

**More examples:**

| | |
|---|---|
| Àwọn ilé | *Houses* |
| Àwọn òbí | *Parents* |
| Àwọn ọmọdé | *Children* |
| Àwọn ilée wọn | *their houses* |
| Ilée wọn | *their house* |
| Àwọn aráà mi | *my people* |
| Ilé òbîì mi | *my parent's house* |
| Ilé àwọn òbîì mi | *my parents' house* |
| Àwọn ilé àwọn òbîì mi | *the houses of my parents* |
| Mo fẹ́ràn àwọn ọmọdé | *I love children* |

 CC – 2012 The University of Texas at Austin

### Iṣẹ́ Ṣíṣe 1

Kọ àwọn gbólóhùn wọ̀nyí ní Yorùbá. Lo **'àwọn'** ni ibi tí ó bá yẹ.
*Write the sentences below in Yorùbá using the plural marker where necessary.*

1. I like her father's books.
2. My hands are clean.
3. I love children.
4. My parent's house is in Austin.
5. I want to buy four books.

### Iṣẹ́ Ṣíṣe 2

Fi àrọ́pò orúkọ tó bá yẹ dí àwọn àlàfo wọ̀nyí.
*Fill out the spaces below with appropriate pronouns.*

Nígbà tí____________ délé, ____________ òbî ____________ bi____________ pé níbo ni ____________ tí ń bọ̀. ____________ pinnu láti sọ òtítọ́ fún____________. ____________ sọ fún wọn pé ọ̀dọ̀ ọ̀rẹ́ẹ̀ ____________ ni ____________ ti ń bọ̀.


CC – 2012 The University of Texas at Austin

# Lesson 3 - Ẹ̀kọ́ Kẹta:
# Nínú Kíláàsì *(In the Classroom)*




## Ọ̀rọ̀ àdásọ *(Monologue)*

### Kíláàsì mi (*My classroom*)

Orúkọ̣ mi ni Wálé. Mo jẹ́ akẹ́kọ̀ọ́ ní Yunifásítì ti Texas ní Austin. Mo fẹ́ràn ilé-ìwéè mi gan-an ni nítorí pé gbogbo ohun tí ó lè mú kí ẹ̀kọ́ rọ ènìyàn lọ́rùn ni ó wà níbẹ̀ àgàgà nínú kíláàsìì mi.

Oríṣiríṣi nǹkan ni ó wà nínú kíláàsìì mi. Láraa wọn ni àga, tábìlì, àwòrán, kọ̀ǹpútà, mọ́nítọ̀, máòsì, kííbọọdù, ìwé atúmọ̀-èdè, pẹ́ẹ̀nì, pẹ́ńsùlù, rúlà, ìrésà, fídíò, síídì, fáìlì, máàpù àgbáyé, ṣọ́ọ̀kì, pátákó-ìkọ̀wé àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ.

Lẹ́yìn èyí, a tún lè rí àwọn nǹkan mìíràn tí wọ́n mú kíláàsìì mi yàtọ̀ sí kíláàsì mìíràn ni Yunifásítì bíi ìlẹ̀kùn aláràbarà, fèrèsé aláràbarà, iná ìlẹ́tíríìkì, àjà, apẹ̀rẹ̀-ìdalẹ̀nùsí àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ.

Mo fẹ́ràn ilé-ìwéè mi lọ́pọ̀lọpọ̀. Mo sì máa ń fi í yangàn lááárín àwọn ọ̀rẹ́ẹ̀ mi nítorí pé náánní náànnì náánní, ohun a ní là á náánní bí ọmọ aṣẹ́gità ṣe ń náánní èpo igi.

## Iṣẹ́ Ṣíṣe 1

Dáhùn àwọn ìbéèrè wọ̀nyí.

*Respond to the following questions.*

| | Òótọ́ ni | Òótọ́ kọ́ |
|---|---|---|
| 1. Ọ̀ṣìṣẹ́ ni Wálé ní Yunifásítì ti Texas ní Austin. | ☐ | ☐ |
| 2. Wálé fẹ̀ránan kíláàsì rẹ̀. | ☐ | ☐ |
| 3. Fááànù wà ní kíláàsì Wálé. | ☐ | ☐ |
| 4. Wálé máa ń fi ilé-ìwé rẹ̀ yangàn. | ☐ | ☐ |
| 5. Wálé máa kúrò ní ilé-ìwé rẹ̀ nítorí pé kò fẹ̀ránan ilé-ìwé rẹ̀. | ☐ | ☐ |

 CC – 2012 The University of Texas at Austin

## Prepositions

Preposition of location is one of the grammatical classes in Yorùbá. 'Ní' combines with the following to form prepositions.

**For example:**

| | | | |
|---|---|---|---|
| Ní + abẹ́ | → | lábẹ́ | *under* |
| Ní + iwájú | → | níwájú | *in front of* |
| Ní + ẹ̀yìn | → | lẹ́yìn | *behind* |
| Ní + ààrín | → | láààrín | *in between / in the middle of* |
| Ní + inú | → | nínú | *inside* |
| Ní + ẹ̀gbẹ́ | → | lẹ́gbẹ̀ẹ́ | *beside* |
| Ní + orí | → | lórí | *on top of* |


These prepositions do not require **ní**:

| | |
|---|---|
| súnmọ́ | *near* |
| jínnà sí | *far from* |


**Wà** ***'to be'*** precedes the preposition to express location. For example:

Ìwé wà lóríi tábìlì → *The book is on the table.*

**Other examples are found below:**




Àga wà níwájúu tábìlì.




Àpò wà lẹ́yìn àga.


 CC – 2012 The University of Texas at Austin




Pẹ́ẹ̀nì wà láàárín ìwé àti àpò.




Pẹ́ńsùlù wà nínú ìwé.



Apẹ̀rẹ̀ ìdalẹ̀nùsí wà lẹ́gbẹ̀ẹ́ ilẹ̀kùn.



Bàtà wà lábẹ́ àga.



Àgá jìnnà sí tábìlì.

 CC – 2012 The University of Texas at Austin

### Iṣẹ́ Ṣíṣe 2

Kọ àwọn gbólóhùn wọ̀nyí ní èdèe Yorùbá.
*Write the following sentences in Yorùbá.*

1. The book is inside the bag.________________________________________
2. The bag is under the table.________________________________________
3. The pencil is beside the bag.______________________________________
4. The table is in front of the chalkboard._______________________________
5. The book is between the pencil and the pen.__________________________
6. I am far from the chalkboard._____________________________________
7. The bag is near the student.______________________________________

### Iṣẹ́ Ṣíṣe 3

Olùkọ́ọ̀ rẹ yó fi àwọn nǹkan kan hàn ẹ́ nínúu kíláàsì. Dáhùn àwọn ìbéèrè tí ó bá tẹ̀lé ìfihàn náà.
*Your teacher will show you some objects in the classroom and their location. Provide a response to your teacher's questions.*

## The interrogativeNíbo *Atọ́ka Àṣebéèrè Níbo*

**'Níbo'** is an interrogative form that means **where?**.
Níbo ni…..? *Where is….?*

The verb **wà** (*to be / to exist)* is used in combination with **níbo ni** to ask a question concerning the location of something or someone.


<u>**For example:**</u>

| | | |
|---|---|---|
| **Ìbéèrè:** | Níbo ni ìwé wà? | *Where is the book?* |
| **Ìdáhùn:** | Ìwé wà lóríi tábìlì. | *(The) book is on the table.* |
| **Ìbéèrè:** | Níbo ni kọ̀ǹpútàá wà? | *Where is the computer?* |
| **Ìdáhùn:** | Kííbọ̀ọ̀dù wà níwájúu kọ̀ǹpútàá. | *The keyboard is in front of the computer.* |

However, **wà** can also be used as a response to indicate how someone is doing, as in the following:

Bàbá ńkọ́? *How is your father doing?*

| Wọ́n wà. | *He is doing fine/well.* |
|---|---|



## Iṣẹ́ Ṣíṣe 4

Wo àwọn àwòrán ti a pèsè sókè láti fi dáhùn àwọn ìbéèrè wọ̀nyí.

*Use the pictures of objects of the classroom and their locations provided above to respond to the following questions*

1. Níbo ni ìwé wà?
______________________________
2. Níbo ni ìrésà wà?
______________________________
3. Níbo ni pẹ́ẹ̀nì wà?
______________________________
4. Níbo ni pẹ́ẹ̀nì àti pẹ́ńsùlù wà?
______________________________
5. Níbo ni pẹ́ńsùlù wà?
______________________________
6. Níbo ni ìwé-atúmọ̀ wà?
______________________________
7. Níbo ni pátákó-ìkọ̀wé wà?
______________________________
8. Níbo ni àga wà?
______________________________
9. Níbo ni àpò wà?
______________________________
10. Níbo ni tábìlì wà?
______________________________

## Iṣẹ́ Ṣíṣe 5

Dáhùn àwọn ìbéèrè wọ̀nyí ní ẹ̀kúnrẹ́rẹ́.

*Answer the following questions in complete sentences.*

1. Níbo ni ìwéè rẹ wà?
______________________________
2. Níbo ni pẹ́ẹ̀nì rẹ wà?
______________________________
3. Níbo ni ìwọ náa wà?
______________________________
4. Níbo ni olùkọ́ọ̀ rẹ wà?
______________________________
5. Níbo ni ọ̀rẹ́ẹ̀ rẹ wà?
______________________________

 CC – 2012 The University of Texas at Austin

## Iṣẹ́ Ṣíṣe 6

Béèrè ìbéèrè márùnún nínú àwọn ìbéèrè tí wọ́n wà ní Iṣẹ́ Ṣíṣe 4 ní ọwọ́ ọ̀rẹ́ẹ̀ rẹ kan nínúu kíláàsì. Kọ àwọn ìdáhùnun rẹ̀ sílẹ̀.
*Ask your friend five questions from exercise 4 above. Write down his or her responses.*

 CC – 2012 The University of Texas at Austin

Wá àwọn ọ̀rọ̀ wọ̀nyí
*Look for these words in the puzzle below. Pay attention to the tones!*
**àga, tábìlì, kọ̀ǹpútà, mọ́nítọ̀, pẹ́ẹ̀nì, pẹ́ńsùlù, ilẹ̀kùn, àjà, tẹlifíṣàn, akẹ́kọ̀ọ́**

| | | | | | | | | | | | | | | |
|---|---|---|---|---|---|---|---|---|---|---|---|---|---|---|
| m | k | ọ̀ | ǹ | p | ú | t | a | à | g | ù | k | e | k | á |
| b | ọ́ | g | á | a | s | á | k | e | k | ọ̀ | ọ̀ | ì | l | ẹ́ |
| g | a | n | ù | y | í | b | ẹ́ | à | n | ẹ́ | n | á | b | k |
| e | s | u | í | à | t | á | k | e | b | ẹ̀ | í | j | ù | u |
| á | ẹ́ | b | a | t | í | k | ọ̀ | k | ẹ́ | o | m | à | u | n |
| í | b | à | b | ù | ọ̀ | b | ọ́ | p | á | m | ọ̀ | n | i | t |
| g | d | k | t | ẹ | l | l | f | í | s | à | n | u | b | à |
| b | ù | b | a | í | ẹ́ | à | i | t | a | b | i | á | g | b |
| à | l | a | t | á | b | ù | l | g | á | n | t | a | b | í |
| l | s | á | k | o | l | í | ẹ̀ | à | t | b | ọ̀ | f | i | s |
| e | í | g | b | ù | d | à | k | ẹ́ | ọ̀ | k | ì | à | g | n |
| b | t | à | s | í | l | k | ù | s | g | á | n | l | j | í |
| k | ù | ń | p | e | g | u | n | à | a | k | o | b | ì | à |
| e | ẹ́ | g | à | l | b | à | g | a | n | o | b | ù | b | à |
| p | e | e | n | í | p | ẹ́ | u | s | b | á | a | g | a | t |

## Iṣẹ́ Ṣíṣe 7

Dárúkọ àwọn nǹkan mẹ́wàá tí ó wà nínúu kíláàsì rẹ kí o sì sọ ibi tí wọ́n wà.
*Mention ten objects in your classroom and provide the location.*

## Iṣẹ́ Ṣíṣe 8

Lo àwọn nǹkan márùnún tí ó wà nínúu kíláàsì yìí ní gbólóhùn pẹ̀lúu **Níbo ni**…, kí o sì pèsè ìdáhùn sí wọn.

*Use five objects in this classroom to form questions with* ***Níbo ni…*** *, and provide answers to your questions.*

**Bí àpẹẹrẹ:**

1a. Níbo ni àgá wà?

1b. Ó wà níwájúu tábìlì.

1a. ______________________________

1b. ______________________________

2a. ______________________________

2b. ______________________________

3a. ______________________________

3b. ______________________________

4a. ______________________________

4b. ______________________________

5a. ______________________________

5b. ______________________________

 CC – 2012 The University of Texas at Austin

# Lesson 4 - Ẹ̀kọ́ Kẹrin: Nọ́ńbà (*Numbers*)

## Nọ́ńbà 0 - 40

| | | | |
|---|---|---|---|
| 0 | òdo | 21 | oókànlélógún |
| 1 | oókan | 22 | eéjìlélógún |
| 2 | eéjì | 23 | ẹẹ́tàlélógún |
| 3 | ẹẹ́ta | 24 | ẹẹ́rìnlélógún |
| 4 | ẹẹ́rin | 25 | aárùnúndínlọ́gbọ̀n |
| 5 | aárùnún | 26 | ẹẹ́rìndínlọ́gbọ̀n |
| 6 | ẹẹ́fà | 27 | ẹẹ́tàdínlọ́gbọ̀n |
| 7 | eéje | 28 | eéjìdínlọ́gbọ̀n |
| 8 | ẹẹ́jọ | 29 | oókàndínlọ́gbọ̀n |
| 9 | ẹẹ́sànán | 30 | ọgbọ̀n |
| 10 | ẹẹ́wàá | 31 | oókànlélọ́gbọ̀n |
| 11 | oókànlá | 32 | eéjìlélọ́gbọ̀n |
| 12 | eéjìlá | 33 | ẹẹ́tàlélọ́gbọ̀n |
| 13 | ẹẹ́tàlá | 34 | ẹẹ́rìnlélọ́gbọ̀n |
| 14 | ẹẹ́rìnlá | 35 | aárùnúndínlógójì |
| 15 | aárùnúndínlógún | 36 | ẹẹ́rìndínlógójì |
| 16 | ẹẹ́rìndínlógún | 37 | ẹẹ́tàdínlógójì |
| 17 | ẹẹ́tàdínlógún | 38 | eéjìdínlógójì |
| 18 | eéjìdínlógún | 39 | oókàndínlógójì |
| 19 | oókàndínlógún | 40 | ogójì |
| 20 | ogún | | |

 CC – 2012 The University of Texas at Austin

## Iṣẹ́ Ṣíṣe 1

Dáhùn àwọn ìbéèrè wọ̀nyí ní ẹ̀kúnrẹ́rẹ́.
*Answer the following questions in complete sentences.*

**Bí àpẹẹrẹ:**

| | | |
|---|---|---|
| 3 + 3 | = | ẹ́ẹ́fà |
| 10 - 6 | = | ẹ́ẹ́rin |
| 3 x 9 | = | ẹ̀ẹ̀tàdínlọ́gbọ̀n |
| 20 / 2 | = | ẹ́ẹ́wàá |

1. 12 + 2 = ______________________
2. 10 + 5 = ______________________
3. 41 –20 = ______________________
4. 18 / 3 = ______________________
5. 2 x 8 = ______________________
6. 20 – 11 = ______________________
7. 15 + 5 = ______________________
8. 8 x 4 = ______________________
9. 19 - 5 = ______________________
10. 24 + 12 = ______________________

## Iṣẹ́ Ṣíṣe 2

Dáhùn àwọn ìbéèrè wọ̀nyí ní ẹ̀kúnrẹ́rẹ́.

*Answer the following questions in complete sentences.*

**Bí àpẹẹrẹ:**

| | |
|---|---|
| 1 + 1 = 2 | Oókan àti oókan jẹ́ eéjì. |
| 7 - 3 = 4 | Yọ ẹ́ẹ́ta kúrò nínú eéjé, ó jẹ́ ẹ́ẹ́rin. |
| 2 x 7 = 14 | Eéjì lọ́nà méje jẹ́ ẹ́ẹ́rìnlá. |
| 18 / 2 = 9 | Fi eéjì pín eéjìdínlógún, ó jẹ́ ẹ́ẹ́sànán. |

1. 7 + 8 = 15 ______________________
2. 19 - 6 = 13 ______________________
3. 15 - 5 = 10 ______________________
4. 18 / 9 = 2 ______________________
5. 4 x 5 = 20 ______________________

## Iṣẹ́ Ṣíṣe 3

Kọ́kọ́ kọ àwọn nọ́ńbà náà sílẹ̀ kí o tó kọ wọ́n ní Yorùbá.
*Write the numbers first in figures then in Yorùbá words.*

1. Kí ni nọ́ńbàa tẹlifóònù rẹ?
______________________
2. Kí ni nọ́ńbàa tẹlifóònù àwọn ọlọ́pàá?
______________________
3. Kí ni nọ́ńbàa tẹlifóònù àwọn panápaná?
______________________
4. Kí ni nọ́ǹbàa tẹlifóònù ilẹ́è rẹ?
______________________
5. Kí ni nọ́ńbàa tẹlifóònù fún nǹkan pàjáwìrì?
______________________

 CC – 2012 The University of Texas at Austin

## Iṣẹ́ Ṣíṣe 4

Dáhùn àwọn ìbéèrè wọ̀nyí ní ẹ̀kúnrẹ́rẹ́.

*Answer the following questions in complete sentences.*

**Bí àpẹẹrẹ:**

Eéjì àti oókan jẹ́ ẹ̀ẹ́ta

1. Eéjì àti ẹ́ẹ́jọ jẹ́? ________________________________________
2. Yọ ẹ́ẹ́fà kúrò nínú eéjìlá, ó jẹ́? ________________________________________
3. Ẹ́ẹ́ta lọ́nà mẹ́fà jẹ́? ________________________________________
4. Yọ eéje kúrò nínú ẹ́ẹ́tàlá, ó jẹ́? ________________________________________
5. Oókànlá àti oókan jẹ́? ________________________________________

## Iṣẹ́ Ṣíṣe 5

So àwọn tí ó bara mu ni ọ̀wọ́ A àti ọ̀wọ́ B papọ̀.

*Match the words in column A with those in column B.*


| A | B |
|---|---|
| Ẹ́ẹ́rin àti ẹ́ẹ́rìndínlógún | ogójì |
| Eéjìlá àti ẹ́ẹ́tàlá | ọgbọ̀n |
| Aárùnún àti aárùnúndínlọ́gbọ̀n | eéjìlélọ́gbọ̀n |
| Oókànlàá àti oókànlélógún | aárùnúndínlọ́gbọ̀n |
| Ẹ́ẹ́tàdínlógún àti ẹ́ẹ́tàlélógún | ogún |

 CC – 2012 The University of Texas at Austin

## Ìsọ̀rọ̀ngbèsì *(Dialogue)*

1.

| | |
|---|---|
| **Olùkọ́:** | Gbogbo yín, ẹ mú ìwé ìṣirò̀o yín jáde. Ẹ ṣí ìwé yín sí ojú-ìwé karùnlélọ́gbọ̀n. Títí, ṣe ìṣirò kìíní. |
| **Títí:** | Aárùnúndínlógún àti ẹ̀ẹ̀tàlá jẹ́ eéjìdínlọ́gbọ̀n. |
| **Olùkọ́:** | Títí, o gba ìṣirò rẹ ṣámúṣámú. Kẹ́mi, ṣe ìṣirò kọkànlá. Yọ ẹ̀ẹ́rin kúrò nínú ẹ̀ẹ̀tàlá. |
| **Kẹ́mi:** | Ẹm ẹm ẹm, ó ku ẹ̀ẹ́sànán. |
| **Olùkọ́:** | O káre, Kẹ́mi. Fọlákẹ́, ṣe ìṣirò tó tẹ̀lé ìyẹn. Yọ ẹ̀ẹ́sànán kúrò nínú ẹ̀ẹ̀tàdínlógún. |
| **Fọlákẹ:** | Ó kù ẹ̀ẹ́jọ. |
| **Olùkọ́:** | Ó káre Fọlákẹ. |




*Nínú kíláàsì, Olùkọ́ àti àwọn ọmọ ilé-íwé ń ṣe ìṣíró.*

*Inside the classroom, the teacher and students are solving math problems*

2.

| | |
|---|---|
| **Olùkọ́**: | Ẹ̀yin ọmọ, ẹ dákẹ́ ariwo. Ọ̀la ni ọjọ́ ìdánwò. Ó yẹ kí á tún ìṣirò̀o wa wò. Lọlá, Kí ni ìṣirò̀o eéjì àti ẹ̀ẹ́fà? |
| **Lọlá**: | Ẹ̀ẹ́jọ ni. |
| **Olùkọ́**: | Ó káre Lọlá. Títí, kí ni oókàndínlógún àti ogún? |
| **Títí**: | Oókàndínlọ́gbọ̀n ni |
| **Olùkọ́**: | Fẹ́mi, ṣé Títí gba ìṣirò̀o rẹ̀? |
| **Fẹ́mi**: | Rárá, oókàndínlógójì ni àròpọ̀ oókàndínlógún àti ogún. |
| **Olùkọ́**: | O káre Fẹ́mi. Rẹ̀mí, yọ aárùnúndínlógún kúrò nínú oókànlélọ́gbọ̀n. |
| **Rẹ̀mí**: | Ẹ̀ẹ́rìndínlógún ni. |
| **Olùkọ́**: | Fúnmi, ṣé Rẹ̀mí gba ìṣirò̀o rẹ̀? |
| **Fúnmi**: | Bẹ́ẹ̀ ni, ó gba ìṣirò̀o rẹ̀. |
| **Olùkọ́**: | Gbogbo yín, ẹ káre. |

 CC – 2012 The University of Texas at Austin



# Chapter 3 - Orí Kęta | MARK THE DATE

## *OBJECTIVES:*

In this chapter you will learn:

- -How to count from 40 to 100
- -How to expess the future
- -How to ask how much…, how many..., and what is the sum of?
- -How to identify the days of the week and months of the year.

## Àwọn ọ̀rọ̀ (*Vocabulary*)

| Nouns | |
|---|---|
| bàtà | *shoe* |
| èṣí | *last year* |
| ìdúnta | *three years ago* |
| ìbéèrè | *question* |
| Ìdáhùn | *answer* |
| Ìpínlẹ̀ | *state* |
| ìtàn | *story* |
| koríko | *grass* |
| òmìnira | *independence* |
| orílẹ̀-èdè | *country* |
| oṣù | *month* |
| ọdún | *year* |
| ọjọ́ | *day* |
| ọ̀la | *tomorrow* |
| ọlọ́pàá | *police officer* |
| ọ̀túnla | *day after tomorrow* |
| panápaná | *fire station* |

| Noun Phrases | |
|---|---|
| ìwée gírámàa Yorùbá | *Yorùbá grammar book* |
| ọdún márùnún sẹ́yìn | *five years ago* |
| ọjọ́ mẹ́rin òní | *three days from now* |
| ọjọ́ márùnún òní | *four days from now* |
| ọjọ́ mẹ́fà òní | *five days from now* |
| ọjọ́ wo…? | *what/which day?* |
| ọdún tí ó kọjá | *last year* |

| Verbs | |
|---|---|
| rà | *to buy* |
| ni | *is* |

| Adjective | |
|---|---|
| yìí | *this* |

# Lesson 1 - Ẹ̀kọ́ Kìíní:

## Nọ́ńbà (*Numbers*) continued

## Nọ́ńbà 40-100

| | |
|---|---|
| 0 | òdo |
| 10 | ẹ́ẹ̀wàá |
| 20 | ogún |
| 30 | ọgbọ̀n |
| 40 | ogójì |
| 41 | oókànlélógójì |
| 42 | eéjìlélógójì |
| 43 | ẹ́ẹ̀tàlélógójì |
| 44 | ẹ́ẹ̀rìnlélógójì |
| 45 | aárùnúndínláàádọ́ta |
| 46 | ẹ́ẹ̀rìndínláàádọ́ta |
| 47 | ẹ́ẹ̀tàdínláàádọ́ta |
| 48 | eéjìdínláàádọ́ta |
| 49 | oókàndínláàádọ́ta |
| 50 | àádọ́ta |
| 60 | ọgọ́ta |
| 70 | àádọ́rin |
| 80 | ọgọ́rin |
| 90 | àádọ́rùnún |
| 100 | ọgọ́rùnún |

**Eélòó:** *How much*

**Eélòó** is an interrogative form that means ***how much?*** However, in terms of solving problems such as addition, subtraction, multiplication, etc., we ask:

Eélòó ni? What is the sum of?

**Bí àpẹẹrẹ:**

Ìbéèrè: Eélòó ni oókan àti oókan jẹ́?
Ìdáhùn: Oókan àti oókan jẹ́ eéjì.

 CC – 2012 The University of Texas at Austin

## Iṣẹ́ Ṣíṣe 1

Kọ ìbéèrè àti ìdáhùn àwọn àròpọ̀ yìí sílẹ̀.
*Write down the questions and answers to the following.*

1. 47 + 38 = ______
2. 39 + 54 = ______
3. 75 + 15 = ______
4. 69 + 19 = ______
5. 44 + 44 = ______

## Iṣẹ́ Ṣíṣe 2

Kọ àwọn ìdáhùn rẹ nìkan sílẹ̀.
*Write down your answers in words only.*

**Bí àpẹẹrẹ:**

100 - 39 = oókànlélọ́gọ́ta.

1. 98 - 43 = ______
2. 100 - 58 = ______
3. 75 - 49 = ______
4. 50 - 25 = ______
5. 80 - 38 = ______


CC – 2012 The University of Texas at Austin

## Iṣẹ́ Ṣíṣe 3

Dáhùn àwọn ìbéèrè wọ̀nyí ní ẹ̀kúnrẹ́rẹ́.

*Answer the following questions in complete sentences.*

**Bí àpẹẹrẹ:**

**Ìbéèrè:** Eélòó ni o ra ìwéè rẹ?

**Ìdáhùn:** Náírà mẹ́rin ni mo ra ìwéè mi.

1. Eélòó ni o ra ìwée gírámàa Yorùbáà rẹ?

   ________________________________________

2. Eélòó ni o ra àpò ìwéè rẹ?

   ________________________________________

3. Eélòó ni o ra bàtàà rẹ?

   ________________________________________

4. Eélòó ni o ra pẹ́ńsùlù rẹ?

   ________________________________________

5. Eélòó ni o ra pẹ́ẹ̀nìì rẹ?

   ________________________________________

 CC – 2012 The University of Texas at Austin

## Lesson 2 - Ẹ̀kọ́ Kejì:
## Future Tense Máa

'Máa' is a future tense marker that can be used with both emphatic and regular pronouns. Below, emphatic and regular pronouns can be used interchangeably.

**For example:**

| | |
|---|---|
| Èmí máa lọ /Mo máa lọ | *I will go* |
| Ìwọ́ máa lọ /O máa lọ | *You will go* |
| Òún máa lọ /Ó máa lọ | *He/She/It will go* |
| Àwá máa lọ /A máa lọ | *We will go* |
| Ẹ̀yín máa lọ /Ẹ máa lọ | *You all (or honorific singular) will go* |
| Àwọ́n máa lọ /Wọ́n máa lọ | *They will go* |

### Emphatic Pronoun + Máa + Negation

| | |
|---|---|
| Èmí máa lọ | Èmi kò nì í lọ |
| Ìwọ́ máa lọ | Ìwọ kò nì í lọ |
| Òún máa lọ | Òun kò nì í lọ |
| Àwá máa lọ | Àwa kò nì í lọ |
| Ẹ̀yín máa lọ | Ẹ̀yin kò nì í lọ |
| Àwọ́n máa lọ | Àwọn kò nì í lọ |

### Regular Pronoun + Máa + Negation

| | |
|---|---|
| Mo máa lọ | N kò nì í lọ |
| O máa lọ | O kò nì í lọ |
| Ó máa lọ | Kò nì í lọ |
| A máa lọ | A kò nì í lọ |
| Ẹ máa lọ | Ẹ kò nì í lọ |
| Wọ́n máa lọ | Wọn kò nì í lọ |

The following also indicate future tense

| | |
|---|---|
| Mà á lọ | *I will go* |
| Wà á lọ | *You will go* |
| Á á lọ | *He/She/It will go* |
| À á lọ | *We will go* |
| Ẹ̀ ẹ́ lọ | *You all will go* |
| Wọ́n á lọ | *They will go* |

## Máa + Yorùbá Calendar

### Ìsọ̀rọ̀ngbèsì *(Dialogue)*

### Ọ̀sẹ̀ tí ó ń bọ̀ (*Next Week*)

**Bàbá Adé**: Bàbá Ọlá, ṣé wà á bámi lọ sí oko ní ọ̀sẹ̀ tí ó ń bọ̀?

**Bàbá Ọlá**: Rárá o, nítorí pé mo máa lọ sí ọ̀dọ̀ àbúròò mi obìnrin tí ara rẹ̀ kò yá. Tí mo bá dé ibẹ̀, mà á ba lọ sí oko láti mú iṣu, ilá, tòmátò, ẹ̀gúsí, ata rodo, tàtàsé àti ẹ̀gẹ́ wá sílé. Tí mo bá dé láti oko, mà á ba se oúnjẹ. Lẹ́yìn náà, mà á ní láti bá a fọṣọ, lọta, kí n sì bá a gé igi. Mà á ba lọ gba oogùn lọ́dọ̀ọ apòògùn. Mà á tọ́jú àbúròò mi dáradára. Mà á dúró tì í títí di alẹ́. Mà á wá padà sí ilée mi.

**Bàbá Adé**: Ó dára o. Mà á sì lọ sí oko láti hú koríko. Tí mo bá ṣe tán, mà á padà wá sílé.

**Bàbá Ọlá**: Bóyá ti ara àbúròò mi obìnrin bá yá tán a má a jọ lọ. Jẹ́ kí á lọ ìsọ̀ọ Màmáa Títí.

**Bàbá Adé**: Ìyẹn á dára púpọ̀.

## Iṣẹ́ Ṣíṣe 1

Dáhùn àwọn ìbéèrè wọ̀nyí ní ẹ̀kúnrẹ́rẹ́.
*Answer the following questions in complete sentences.*

1. Ta ni ó ń lọ sí ọ̀dọ̀ àbúròo rẹ̀?
2. Tí Bàbá Ọlá bá dé ibẹ̀, kí ni ó máa ṣe?
3. Kí ni Bàbá Adé àti Bàbá Ọlá máa ṣe nígbà tí ara àbúròo Bàbá Ọlá bá yá tán?
4. Kí ni ìdìi rẹ̀ tí Bàbá Ọlá fi máa tọ́jú àbúròo rẹ̀ dáradára?
5. Ta ni Bàbá Adé?

## Iṣẹ́ Ṣíṣe 2

Dáhùn àwọn ìbéèrè wọ̀nyí ní ẹ̀kúnrẹ́rẹ́.
*Answer the following questions in complete sentences.*

1. Kí ni o máa ṣe ní ọ̀sẹ̀ tí ó mbọ̀?
2. Kí ni o máa ṣe ní ààrọ̀ ọ̀la?
3. Kí ni o máa ṣe ní ìparí ẹ̀kọ́ọ̀ rẹ ní yunifásítì?
4. Kí ni o máa ṣe ní ọjọ́ àbámẹ́ta ?
5. Kí ni o máa ṣe ní ọjọ́ọ ìsinmi tí ó ḿbọ̀?

 CC – 2012 The University of Texas at Austin

## Lesson 3 - Ẹ̀kọ́ Kẹta

### *The Yorùbá Calendar (Days of the Week)*

| Days of the Week | Ọjọ́ nínú ọ̀sẹ̀ | |
|---|---|---|
| Sunday: | Ọjọ́ Àìkú | *day of not dying (day of rest)* |
| Monday: | Ọjọ́ Ajé | *day of commerce* |
| Tuesday: | Ọjọ́ Ìṣẹ́gun | *day of victory* |
| Wednesday: | Ọjọ́rú | *day of confusion* |
| Thursday: | Ọjọ́bọ̀ | *day of sacrifice* |
| Friday: | Ọjọ́ Ẹtì | *day of impossibility* |
| Saturday: | Ọjọ́ Àbámẹ́ta | *day of three resolutions* |

However, many Yorùbá people substitute the following borrowings below for the traditional days of the week above:

| | |
|---|---|
| Sunday: | Ọjọ́ọ Sọ́ńdè / Ọjọ́ ọ̀ṣẹ̀ (Ọjọ́ọ̀sinmi) |
| Monday: | Ọjọ́ọ Mọ́ńdè |
| Tuesday: | Ọjọ́ọ Túsìdeè |
| Wednesday: | Ọjọ́ọ Wẹ́sìdeè |
| Thursday: | Ọjọ́ọ Tọ́sìdeè |
| Friday: | Ọjọ́ọ Fúráìdeè |
| Saturday: | Ọjọ́ọ Sátidé |

Yorùbá people also refer to Thursday as Ọjọ́ Àlàmísì, and Friday as Ọjọ́ọ Jímọ́ọ̀.

 CC – 2012 The University of Texas at Austin




## Ọ̀rọ̀ àdásọ (*Monologue*)

Orúkọ mi ni Wálé. Mo jẹ́ ọmọ bíbí ìlú Ìbàdàn láti ìpínlẹ̀ Ọ̀yọ́ ní orílẹ̀-èdè Nàìjíríà. Tí ó bá di ọjọ́ kẹsàn-án, oṣù kọkànlá ọdún tí ó ń bọ̀ ni màá pé ọmọ ọdún mọ́kàndínlọ́gbọ̀n.
Gẹ́gẹ́ bí ìtàn tí mo gbọ́, torí bí ọ́mọdé kò bá gbọ́ ìtàn, yóò gbọ́ àrọ́bá torí pé àrọ́bá ni bàbá ìtàn. Mo gbọ́ pé ọjọ́ ìṣẹ́gun ni ọjọ́ tí àwọn òbí mi bí mi. Èyí máa ń jẹ́ kí inúù mi dùn fún ọjọ́-ìbí mi tí ó bá bọ́ sí ọjọ́ ìṣẹ́gun.
Nípa ti àwọ̀, kí n má purọ́, mo fẹ́ràn àwọ̀ ṣùgbọ́n n kò fẹ́ràn àwọ̀ pupa àti yẹ́lò rárá rárá. Gbogbo ohun tí ẹnu ń jẹ pátá ni mo fẹ́ràn.

### Iṣẹ́ Ṣíṣe 1

Sọ **'bẹ́ẹ̀ ni'** tàbí **'bẹ́ẹ̀ kọ́'** fún àwọn gbólóhùn wọ̀nyí.
*State whether the following sentences are true or false.*

| | Òótọ́ ni | Òótọ́ kọ́ |
|---|---|---|
| 1. Wálé fẹ́ràn oúnjẹ. | ☐ | ☐ |
| 2. Ọmọ ìlú Ọ̀yọ́ ni Wálé. | ☐ | ☐ |
| 3. Ọmọ ọdún méjìdínlógún ni Wálé báyìí. | ☐ | ☐ |
| 4. Ọjọ́ àbáméta ni wọ́n bí Wálé. | ☐ | ☐ |
| 5. Gbogbo àwọ̀ ni Wálé fẹ́ràn. | ☐ | ☐ |

### Iṣẹ́ Ṣíṣe 2

Dáhùn àwọn ìbéèrè wọ̀nyí ní ẹ̀kúnrẹ́rẹ́.
*Answer the following questions in complete sentences.*

1. Tí Wálé bá ṣe ọjọ́-ìbíi rẹ̀ ní ọjọ́-ìṣẹ́gun ní ọdún yìí, ọjọ́ wo ni ó máa ṣe é ní ọdún tí ó ń bọ̀?
2. Ṣàlàyé irú ènìyàn tí Wálé jẹ́.
3. Irú àwọn oúnjẹ wo ni Wálé fẹ́ràn?
4. Ǹjẹ́ ìwọ rò pé Wálé lè ṣe ìrìn-àjò lọ sí ilẹ̀ òkèèrè?
5. Kí ni ó máa ń mú inúu Wálé dùn?


CC – 2012 The University of Texas at Austin

## Iṣẹ́ Ṣíṣe 3

Dáhùn àwọn ìbéèrè wọ̀nyí ní ẹ̀kúnrẹ́rẹ́.
*Answer the following questions in complete sentences.*

1. Ọjọ́ wo ni ọjọ́ kìíní oṣù kẹta ọdún yìí?
   ______________________________
2. Ọjọ́ wo ni ọjọ́ kejìdínlógún oṣù kẹrin ọdún yìí?
   ______________________________
3. Ọjọ́ wo ni ọjọ́ kọkàndínlógún oṣù kẹfà ọdún yìí?
   ______________________________
4. Ọjọ́ wo ni ọjọ́ kejìlá oṣù kẹjọ ọdún yìí?
   ______________________________
5. Ọjọ́ wo ni ọjọ́ kẹtàlèlógún oṣù kejìlá ọdún yìí?
   ______________________________


CC – 2012 The University of Texas at Austin

## Lesson 4 - Ẹ̀kọ́ Kẹrin:

## The Yorùbá Calendar *Kàlẹ́ńdà Yorùbá (Months of the Year)*

| Oṣù nínú Ọdún | | Months of the Year |
|---|---|---|
| Oṣù kìíní ọdún (Ṣẹ́rẹ́) | *first month of the year* | *January* |
| Oṣù kejì ọdún (Èrèlé) | *second month of the year* | *February* |
| Oṣù kẹta ọdún (Ẹrẹ́nà) | *third month of the year* | *March* |
| Oṣù kẹrin ọdún (Igbe) | *fourth month of the year* | *April* |
| Oṣù karùnún ọdún (Èbìbí) | *fifth month of the year* | *May* |
| Oṣù kẹfà ọdún (Òkudù) | *sixth month of the year* | *June* |
| Oṣù keje ọdún (Agẹmọ) | *seventh month of the year* | *July* |
| Oṣù kẹjọ ọdún (Ògún) | *eighth month of the year* | *August* |
| Oṣù kẹsànán ọdún (Ọ̀wẹrẹ̀) | *ninth month of the year* | *September* |
| Oṣù kẹwàá ọdún (Ọ̀wàrà) | *tenth month of the year* | *October* |
| Oṣù kọkànlá ọdún (Belú) | *eleventh month of the year* | *November* |
| Oṣù kejìlá ọdún (Ọpẹ́) | *twelfth month of the year* | *December* |

 CC – 2012 The University of Texas at Austin

## Iṣẹ́ Ṣíṣe 1

Dáhùn àwọn ìbéèrè wọ̀nyí.
*Answer the following questions.*

**Bí àpẹẹrẹ:**

Oṣù wo ni oṣù kẹta ọdún?
Oṣù ẹrẹ̀nà (march)

1. Oṣù wo ni oṣù kejì ọdún?
2. Oṣù wo ni oṣù kejìlá ọdún?
3. Oṣù wo ni oṣù keje ọdún?
4. Oṣù wo ni oṣù karùnún ọdún?
5. Oṣù wo ni oṣù kọkànlá ọdún?

## Iṣẹ́ Ṣíṣe 2

Dáhùn àwọn ìbéèrè wọ̀nyìí
*Answer the following questions.*

1. Oṣù wo ni à ń ṣe ọdúnun Kérésìmesì?
2. Oṣù wo ni à ń ṣe ọdúnun ìdúpẹ́ (Thanksgiving) ní ọdún yìí?
3. Oṣù wo ni à ń ṣe ọdún tuntun?
4. Oṣù wo ni ọjọ ìbíì rẹ?
5. Oṣù wo ni ọjọ ìbíi bàbáà rẹ?

 CC – 2012 The University of Texas at Austin

## Iṣẹ́ Ṣíṣe 3

So àwọn tí ó bara mu ni ọ̀wọ́ A àti ọ̀wọ́ B papọ̀.
*Match the words in column A with those in column B.*

| A | B |
|---|---|
| 9th month | oṣù keje |
| 7th month | oṣù kẹfà |
| 6th month | oṣù kẹta |
| 3rd month | oṣù kẹsànán |
| 1st month | oṣù kẹwàá |
| 8th month | oṣù kìíní |
| 10th month | oṣù kẹjọ |
| 12th month | oṣù kejì |
| 11th month | oṣù kọkànlá |
| 2nd month | oṣù kejìlá |

## Iṣẹ́ Ṣíṣe 4

Dáhùn àwọn ìbéèrè wọ̀nyí.
*Answer the following questions.*

**Bí àpẹẹrẹ:**

8/12 = December 8 = Ọjọ́ kẹjọ oṣù kejìlá ọdún

1. 16/2 = ____________________
2. 21/11 = ____________________
3. 17/ 9 = ____________________
4. 21/ 6 = ____________________
5. 30/ 4 = ____________________


CC – 2012 The University of Texas at Austin

## Iṣẹ́ Ṣíṣe 5

Parí àwọn ọ̀rọ̀ wọ̀nyí:
*Complete the following:*

**Bí àpẹẹrẹ:**

osù mẹ́ta = ọ̀sẹ̀ méjìlá. ____

1. ọ̀sẹ̀ kan = ọjọ́ ____
2. osù kan = ọ̀sẹ̀ ____
3. ọdún kan = osù ____
4. osù méjì = ọ̀sẹ̀ ____
5. ọ̀sẹ̀ mẹ́ta = ọjọ́ ____


CC – 2012 The University of Texas at Austin



## Chapter 4 - Orí Kẹrin | WHAT TIME DO WE MEET?

### *OBJECTIVES:*

In this chapter you will learn:

- How to express quantity using 'mélòó'
- How to ask time using 'mélòó'
- How to express your age using 'mélòó'
- Colors in Yorùbá Culture

## Àwọn ọ̀rọ̀ (*Vocabulary*)

| Nouns | |
|---|---|
| èédú | *charcoal* |
| ewé | *leaf (green color)* |
| gàárí | *cassava grains* |

| Noun Phrases | |
|---|---|
| ibi ọjọ́-ìbí | *birthday venue* |
| ìsìn àgbà | *adults' worship* |
| ìsìn ọmọdé | *children's service/worship* |

| Verbs | |
|---|---|
| bẹ̀rẹ̀ | *to start* |
| dé | *to arrive* |
| fẹ́ | *to want/wish* |
| jí | *to wake up* |
| lọ | *to go* |
| máa | *will* |
| ní | *to have* |
| wá | *to come* |
| wà | *to be or to exist* |

| Verb Phrases | |
|---|---|
| bá mi ṣeré | *play with me* |
| gbá ilẹ̀ | *to sweep the floor* |
| jẹun ọ̀sán | *to eat lunch* |
| jẹun alẹ́ | *to eat dinner* |
| jẹ́ kí á pàdé | *let us meet* |
| sọ fún… | *to tell…(e.g. someone)* |

| Adjectives | |
|---|---|
| búlúù | *blue* |
| dúdú | *black* |
| funfun | *white* |
| pînkì | *pink* |

| | |
|---|---|
| yẹn | *that* |
| yẹ́lò | *yellow* |

## Adverbs

| | |
|---|---|
| bíi / bí | *like* |
| díẹ̀ | *a little* |
| ganan ni | *a lot (very)* |
| kúkú | *just* |

## Conjunctions

| | |
|---|---|
| tí..bá | *if* |
| nítorí pé | *because* |

## Prepositional phrases

| | |
|---|---|
| ní ẹ̀yìn ọ̀sẹ̀ | *at the end of the week* |
| ní ọ̀dọ̀ Akin | *at Akin's place* |
| lójoojúmọ́ | *everyday* |
| lẹ́yìn náà | *following that /after that* |

## Interrogatives

| | |
|---|---|
| Nígbà wo ni ? | *when?* |

## Other Expressions

| | |
|---|---|
| ó dára | *that's fine* |
| ó funfun bí eérú | *It is white like ashes (grey)* |
| Olórí ìlú Àmẹ́ríkà | *The President of the United States of America* |
| ọmọ ọdún mélòó? | *how old?* |
| O ṣé | *thank you* |
| ó ti pẹ́ jù | *It is too late* |
| ó ti yá jù | *It is too early* |

 CC – 2011 The University of Texas at Austin

# Lesson 1 - Ẹ̀kọ́ Kìíní

## The Interrogative Mélòó

Remember how to count from 1 – 10, as we already learned in Chapter 2 and as found below under 'numbers.' Cardinals act like adjectives – they follow the noun that they describe and answer the question **mélòó?** '*how many?*'

| Numbers | Cardinals | English |
|---|---|---|
| oókan | kan | one |
| eéjì | méjì | two |
| ẹẹ́ta | mẹ́ta | three |
| ẹẹ́rin | mẹ́rin | four |
| aárùnún | márùnún | five |
| ẹẹ́fà | mẹ́fà | six |
| eéje | méje | seven |
| ẹẹ́jọ | mẹ́jọ | eight |
| ẹẹ́sànán | mẹ́sànán | nine |
| ẹẹ́wàá | mẹ́wàá | ten |
| oókànlá | mọ́kànlá | eleven |
| eéjìlá | méjìlá | twelve |

**For example:**

**Ìwé mélòó ni ó wà ní oríi tábìlì?** *How many books are on the table?*

One will respond by using the cardinal:


**Ìwé mẹ́ta ni ó wà lóríi tábìlì** *There are three books on the table.*


Also, the numbers in between the multiples of 10 will take an ‘m’ before them.

<u>For example:</u>

| | |
|---|---|
| ọmọ mẹ́tàdínlógún | seveenteen children |
| àga méjì | two chairs |
| ìwé mẹ́tàlá | thirteen books |







However, we do not say *àga **mókan**–***one chair***
One would rather say **àga kan**

Below are examples of multiples of ten:

| | |
|---|---|
| ogún ìyàwó | *twenty wives* |
| àádọ́ta ìgbà | *fifty times* |
| ọgọ́rùnún ọdún | *hundred years* |
| ọgọ́tà ilé | *sixty houses* |
| ọgbọ̀n èniyàn | *two hundred people* |

 CC – 2011 The University of Texas at Austin

## Iṣẹ́ Ṣíṣe 1

*Write out the following in Yorùbá.*

**Bí àpẹẹrẹ:**

80 people Ọgọ́rin ènìyàn

13 books ìwé mẹ́tàlá

1. 18 houses__________
2. 38 pencils__________
3. 62 tables__________
4. 40 students__________
5. 80 pencils__________
6. 75 schools__________
7. 54 children__________
8. 46 teachers__________
9. 20 computers__________
10. 6 desks__________

 CC – 2011 The University of Texas at Austin

## Iṣẹ́ Ṣíṣe 2

Remember the verbs **ní** (to have), **fẹ́** (to want/to wish), **wà** (to be or to exist)

Dáhùn àwọn ìbéèrè wọ̀nyí ní ẹ̀kúnrẹ́rẹ́.
*Answer the following questions in complete sentences.*

1. Ìwé mélòó ni o ní?

   ______________________

2. Ọmọ mélòó ni Òbámà, olórí orílẹ̀-èdè Àmẹ́ríkà, bí(to give birth to)?

   ______________________

3. Àbúrò mélòó ni o ní?

   ______________________

4. Ilé mélòó ni o fẹ́?

   ______________________

5. Ìpínlẹ̀ mélòó ni o wà ní orílẹ̀-èdè Àmẹ́ríkà?

   ______________________

6. Ìpínlẹ̀ mélòó ni ó wà ní orílẹ̀-èdè Nàìjíríà?

   ______________________

7. Kọ̀ǹpútà mélòó ni ó wà nínúu kíláàsìi Yorùbáà rẹ?

   ______________________

8. Akẹ́kọ̀ọ́ obìnrin mélòó ni ó wà nínúu kíláàsì Yorùbáà rẹ?

   ______________________

9. Akẹ́kọ̀ọ́ ọkùnrin mélòó ni ó wà nínúu kíláàsì Yorùbáà rẹ?

   ______________________

10. Pátákó ìkọ̀wé mélòó ni ó wà nínúu kíláàsíi Yorùbáà rẹ?

    ______________________

 CC – 2011 The University of Texas at Austin

## Iṣẹ́ Ṣíṣe 3

In pairs, a student should ask his or her partner the number of people—men, women, or children in that partner's family, with the partner responding. Students take turns.

1. A. ______________________________
   B. ______________________________

2. A. ______________________________
   B. ______________________________

3. A. ______________________________
   B. ______________________________

4. A. ______________________________
   B. ______________________________

5. A. ______________________________
   B. ______________________________

 CC – 2011 The University of Texas at Austin

## Lesson 2 - Ẹ̀kọ́ Kejì

## Aago mélòó ni ó lù? (*What time is it?)*

**Remember in Chapter One we discussed how to distinguish between a.m. and p.m.**

| | |
|---|---|
| àárọ̀ | from about 4:00am to 11:59 am |
| ọ̀sán | from about noon to 4:59 pm |
| ìrọ̀lẹ́ | from about 5:00 pm to 6:59 pm |
| alẹ́ | from about 7:00 pm to 10:00 or 11:59 pm |

**Other expressions of time:**

| | | |
|---|---|---|
| Àbọ̀ | = | half (or 30 minutes past the hour) as in **aago kan àbọ̀ òru =1:30 am** |
| Ku | = | to or less than the hour as in **aago mẹ́ta ọ̀sán ku ogún ìṣẹ́jú = 2:40pm** |
| Kọjá | = | past/after as in **aago mẹ́fà ìrọ̀lẹ́ kọjá ìṣẹ́jú mẹ́ta = 6:03pm** |

**Other expressions:**

Ó ti pẹ́ jù = It is too late

Ó ti yá jù =It is too early

Different times of the day such as àárọ̀, ọ̀sán, ìrọ̀lẹ́, and alẹ́ express how we distinguish time(aago). See exercises below and write down the indicated times.

## Iṣẹ́ Ṣíṣe 1

*Complete the following exercices. The first one has been done for you.*

1. aago kan ọ̀sán = 1pm
2. aago méjì òru = ____
3. aago méjìlá ọ̀sán = ____
4. aago kan àbọ̀ òru = ____
5. aago mẹ́fà ìrọ̀lẹ́ kọjá ìṣẹ́jú mẹ́ta = ____
6. aago méje alẹ́ ku ìṣẹ́jú mẹ́wàá = ____
7. aago mẹ́ta ọ̀sán ku ogún ìṣẹ́jú = ____
8. aago márùnún àárọ̀ kọjá ìṣẹ́jú márùnúndínlógún = ____
9. aago méjìlá òru = ____
10. aago mẹ́rin àárọ̀ = ____

 CC – 2011 The University of Texas at Austin



## Ìsọ̀rọ̀ǹgbèsì *(Dialogue)*

### Lẹ́yìn ìjáde ilé-ìwé

| | |
|---|---|
| **Jìmí**: | Fèyí, ṣé wà á wá kí mi ní òpin ọ̀sẹ̀, ní ọjọ́ àìkú? |
| **Fèyí**: | Ní aago mélòó ni o fẹ́ kí n wá? Ó máa dára ní ọ̀sán nítorí pé mo máa ń lọ sí ìsìn ọmọdé ní aago mẹ́sànán àbọ̀ àárọ̀. Lẹ́yìn náà, ní aago mẹ́wa, ìsìn àgbà máa bẹ̀rẹ̀. |
| **Jìmí**: | (Èmi náà), ní aago márùnún ìrọ̀lẹ́, mo ń lọ sí ibi ọjọ́ ìbí ọ̀rẹ́ẹ̀ mi kan. |
| **Fèyí**: | Ọjọ́ ìbíi ta ni? |
| **Jìmí**: | Ọjọ́ ìbí Akin Ọmọ́yẹmí. |
| **Fèyí**: | Rárá o, aago mẹ́ta ni ọjọ́ ìbí Akin yẹn. Tí o bá lọ ní aago márùnúun, wà á kàn lọ gbá ilẹ̀ ni! |
| **Jìmí**: | O ò ṣe kúkú jẹ́ kí á pàdé ní ọ̀dọ̀ Akin. Ṣé wà á sọ fún àwọn òbíì rẹ? |
| **Fèyí**: | Nígbà wo ni o máa dé ọ̀dọ̀ Akin? |
| **Jìmí**: | Bíi aago mẹ́ta àbọ̀ ọ̀sán. |
| **Fèyí**: | Ó dára, ó dìgbà kan ná. |



*Lẹ́yìn ìjáde ilé-ìwé, Jìmí ń bá Fèyí sọ̀rọ̀*

### Iṣẹ́ Ṣíṣe 2

Dáhùn àwọn ìbéèrè wọ̀nyí ní ẹ̀kúnrẹ́rẹ́.

*Answer the following questions in complete sentences*


1. Aago mélòó ni Jìmí máa dé ọ̀dọ̀ Akin?
2. Ta ni Fèyí?
3. Ọjọ́ ìbíi ta ni Fèyí àti Jìmí fẹ́ ẹ́ lọ?
4. Ta ni Akin Ọmọ́yẹmí?
5. Aago mélòó ni Fèyí máa ń lọ sí ìsìn ọmọdé?


CC – 2011 The University of Texas at Austin

## Iṣẹ́ Ṣíṣe 3

Aago mélòó ni ó lù lórí àwọn aago wọ̀nyí?

*What time is it on the following clocks?*



 CC – 2011 The University of Texas at Austin

## Máa ń + Time

### Iṣẹ́ Ṣíṣe 4

Dáhùn àwọn ìbéèrè wọ̀nyí ní ẹ̀kúnrẹ́rẹ́.
*Answer the following questions in complete sentences.*

**Bí àpẹẹrẹ:**

Aago mélòó ni kíláàsì èdèe Gẹ̀ẹ́sì rẹ máa ń bẹ̀rẹ̀?

Aago mẹ́wàá ààrọ̀ ni kíláàsì èdèe Gẹ̀ẹ́sì mi máa ń bẹ̀rẹ̀.

1. Aago mélòó ni kíláàsì èdèe Yorùbáà rẹ máa ń bẹ̀rẹ̀?
2. Aago mélòó ni o máa ń jí lójóojúmọ́?
3. Aago mélòó ni o máa ń jẹ́ ouńjẹ ọ̀sán?
4. Aago mélòó ni o máa ń jẹ́ ouńjẹ alẹ́?
5. Aago mélòó ni o máa ń sùn ní alẹ́?
6. Aago mélòó ni kíláàsìì rẹ àkọ́kọ́ ń bẹ̀rẹ̀ ní ọjọ́ àìkú?
7. Aago mélòó ni gbogbo kíláàsìì rẹ ń parí ní ọjọ́ Àlàmísì?
8. Kí ni o máa ń ṣe ní aago mẹ́ta ọ̀sán ní ọjọ́ọ Mọ́ńdè?
9. Kí ni o máa ń ṣe ní aago mẹ́sànán alẹ́ ní ọjọ́ọ Jímọ́ọ̀?
10. Kí ni o máa ń ṣe ní aago méje ààrọ̀ ní ọjọ́ ọ̀sẹ̀?

 CC – 2011 The University of Texas at Austin

## Iṣẹ́ Ṣíṣe 5

Ìwọ àti ọ̀rẹ́ẹ̀ rẹ, ẹ ṣọ fún ara yín ìgbà tí ẹnìkọ̀ọ̀kan nínúu yín ń lọ sí kíláàsì àti wí pé kíláàsì wo ni?

*You and your friend, tell each other what time you go to class and what class you have.*

**Bí àpẹẹrẹ:**

**Dúpẹ́:** Aago mélòó ni kíláàsì Bàọ́lọ́jì rẹ máa ń bẹ̀rẹ̀ ní ọjọ́ọ Túsìdeè?

**Tósìn:** Aago méjì ni.

**Dúpẹ́:** Kí ni o ní ni aago mẹ́rin?

**Tósìn:** Mo ní Kẹ́mísìrì.

**Dúpẹ́:** ________________________

**Tósìn:** ________________________

## Iṣẹ́ Ṣíṣe 6

Èyí ni àtẹ àkókò iṣẹ́ẹ Ṣadé fún ọ̀sẹ̀ kan

*This is Ṣade's schedule for the week.*

| Àkókò | Ajé | Ìṣégun | Ọjọ́rú | Ọjọ́bọ̀ | Ẹtì |
|---|---|---|---|---|---|
| 9-10 | Èdèe Gẹ̀ẹ́sì | Ìṣirò | | Físíìsì | Ìṣirò |
| 10-11 | Ìṣirò | Físíìsì | Potogí | | Potogí |
| 11-12 | Faransé | Èdèe Gẹ̀ẹ́sì | Físíìsì | Ìṣirò | Èdèe Gẹ̀ẹ́sì |
| 12-1 | Físíìsì | | Yorùbá | Kẹ́mísírì | |
| 1-2 | Bàọ́lọ́jì | Kẹ́mísìrì | Èdèe Gẹ̀ẹ̀sì | Yorùbá | Kẹ́mísìrì |
| 2-3 | Yorùbá | Faransé | Yorùbá | Faransé | Físíìsì |
| 3-4 | | | Ìṣirò | Èdèe Gẹ̀ẹ̀sì | Faransé |
| 4-5 | Kẹ́mísìrì | Potogí | | Potogí | Yorùbá |
| 5-7 | Láàbù | | | Láàbù | |

Dáhùn àwọn ìbéèrè wọ̀nyí.
*Answer the following questions.*

1. Mélòó ni àpapọ̀ọ gbogbo iṣẹ́ tí Ṣadé ń ṣe lọ́sẹ̀?
2. Iṣẹ́ wo ni Ṣadé ní láago mẹ́wàá àárọ̀ ọjọ́ ajé?
3. Tí ó bá di ọjọ́rú ní aago mẹ́sànán àárọ̀, Ṣadé máa wà nínú kíláàsì wo?
4. Wákàtí mélòó ni Ṣadé fi ń ṣe èdèe Gẹ̀ẹ́sì ní ọ̀sẹ̀?
5. Ǹjẹ́ Ṣadé ní iṣẹ́ kankan ní ọjọ́ àbámẹ́ta?

## Iṣẹ́ Ṣíṣe 7

Using the exercise 3 above, prepare your class schedule using Yorùbá language. Indicate the time you have each class and who your teachers are. Below, you will find a list of courses to help you. If your course is not listed, ask your teacher.

| | |
|---|---|
| Bàọ́lọ́jì | *Biology* |
| Kẹ́mísìrì | *Chemistry* |
| Físîsì | *Physics* |
| Èdèe Faransé | *French language* |
| Èdèe Sípánîṣì | *Spanish language* |
| Ẹ̀kọ́ nípa Òṣèlú | *Government* |
| Lìǹgúísîkì | *Linguistics* |
| Èdèe Gẹ̀ẹ́sì | *English* |
| Láàbù | *Lab work* |
| Èdèe Yorùbá | *Yorùbá language* |
| Èdèe Potogí | *Portuguese language* |
| Ẹ̀kọ́ Ìtàn | *History* |
| Saikọ́lọ́jì | *Psychology* |
| Sosiọ́lọ́jì | *Sociology* |
| Ẹ̀kọ́ nipa ọ̀rọ̀ ìṣèlú | *Political Science* |
| Ẹ̀kọ́ nípa ọ̀rọ̀ ajé | *Economics* |
| Lítíréṣọ̀ | *Literature* |

## Iṣẹ́ Ṣíṣe 8

Parí ìsọ̀rọ̀ngbèsì yìí nípa lílo àwọn àkókò àti òṣùu Yorùbá (Gbólóhùn méjìlá sí márùnúndínlógún).

*Complete the short dialogue below using time and Yoruba calendar (12-15 sentences).*

Ládi pe Kúnlé pé kí ó wá gbá bọ́ọ̀lù pẹ̀lú òun.

*Ládi invites Kúnlé to play soccer with him.*

| | |
|---|---|
| **Ládi**: | Kúnlé, ṣé wà á wá sí ilée wa láti wá gbá bọ́ọ̀lù ní ìrọ̀lẹ́ ọ̀la? |
| **Kúnlé**: | Ó dára. Mà á sọ fún màmáà mi. Aago mélòó ni kí n wá? |
| **Ládi**: | Ní aago márùnún àbọ̀ ìrọ̀lẹ́. Màá máa retí rẹ o. |
| **Kúnlé**: | ________________________ |
| **Ládi**: | ________________________ |

## Iṣẹ́ Ṣíṣe 9

Wá àwọn ọ̀rọ̀ wọ̀nyí

*Look for these words in the puzzle below. Pay attention to the tones!*

**èdè, gẹ̀ẹ́sì, ìṣirò, kẹ́mísìrì, físíìsì, faransé, lìǹgúísíìkì, láàbù, potogí, lítíréṣọ̀**

| | | | | | | | | | | | | | | |
|---|---|---|---|---|---|---|---|---|---|---|---|---|---|---|
| è | l | i | t | i | r | e | k | ẹ́ | m | í | s | ì | r | ì |
| d | d | f | a | r | a | n | s | é | ù | b | i | s | l | l |
| è | g | e | f | i | s | i | i | s | m | ù | r | o | s | ì |
| e | d | e | ọ̀ | p | o | t | ò | k | í | ì | o | s | i | ǹ |
| g | e | ẹ̀ | é | b | o | h | i | l | a | à | s | u | n | g |
| ì | ṣ | i | r | ò | r | t | l | a | à | b | ù | r | ọ̀ | ú |
| í | s | ẹ́ | g | u | n | u | o | l | e | d | e | g | ì | í |
| k | e | i | m | s | i | l | ẹ́ | g | ì | b | a | ọ̀ | l | s |
| f | i | s | r | i | s | ọ̀ | í | l | í | ǹ | ọ̀ | m | b | í |
| r | u | l | a | ò | d | s | i | t | a | m | g | ọ̀ | j | ì |
| g | ẹ̀ | e | s | l | i | k | a | á | í | à | f | u | n | k |
| ẹ̀ | l | a | b | ì | d | e | k | e | b | r | b | n | i | ì |
| ẹ́ | d | á | s | l | á | à | b | ù | n | h | é | ù | m | g |
| s | e | i | á | b | u | l | i | t | i | r | e | ṣ | ọ̀ | ǹ |
| ì | f | í | s | í | ì | s | ì | n | s | i | d | f | ọ̀ | l |

## Iṣẹ́ Ṣíṣe 10 Scenarios

In pairs, create your own dialogue on planning on eating in a restaurant.

 CC – 2011 The University of Texas at Austin

# Lesson 3 - Ẹ̀kọ́ Kẹta:

## *Asking for Age*

When you want to ask 'how old' you will ask: 'ọmọ ọdún mélòó?' For example, if you want to ask how old Tèmi is, you will ask: Ọmọ ọdún mélòo ni Tèmi?

And the response:

Ọmọ ọdún méjì ni Tèmi.
*Tèmi is 2 years old.*

### Telling how old you are

Túndé fẹ́ mọ̀ nípa ọjọ́-orí àwọn ẹbíi Yẹmí.
*Túndé wants to know how old Yẹmí's family members are.*

. Ìsọ̀rọ̀ngbèsì *(Dialogue)*

Yẹmí, Ọmọ ọdún mélòó ni ẹ́?

Ọmọ ọdún méjìdínlógún ni mí.

Ọmọ ọdún mélòó ni bàbáà rẹ?

Ọmọ ọdún mẹ́tàlélógójì ni wọ́n.

Ọmọ ọdún mélòó ni màmáà rẹ?

Ọmọ ogójì ọdún ni wọ́n.

Ọmọ ọdún mélòó ni àbúròo bàbáà rẹ?

Ọmọ ọgbọ̀n ọdún ni wọ́n.

Ọmọ ọdún mélòó ni ẹ̀gbọ́nọ̀n rẹ?

Ọmọ ogún ọdún ni wọ́n.

Ọmọ ọdún mélòó ni àbúròò rẹ?

Ọmọ ọdún mẹ́rìndínlógún ni.



*Túndé fẹ́ mọ̀ nípa ọjọ́-orí àwọn ẹbíi Yẹmí.*

*Túndé wants to know how old Yẹmí's family members are.*

 CC – 2011 The University of Texas at Austin

## Iṣẹ́ Ṣíṣe 1

Dáhùn awọn ìbéèrè wọ̀nyí nípa lílo àpẹẹrẹ tí ó wà ní ìsàlẹ̀ yìí.
*Follow this pattern below to answer the following questions.*

**Bí àpẹẹrẹ:**

Ọmọ ọdún mélòó ni ẹ̀gbọ́n̄ọ̀n rẹ? 30 years old
Ọmọ ọgbọ̀n ọdún ni ẹ̀gbọ́n̄ọ̀n mi.

1. Ọmọ ọdún mélòó ni bàbáà rẹ? 70 years old

   ______________________________

2. Ọmọ ọdún mélòó ni àǹtíì rẹ? 34 years old

   ______________________________

3. Ọmọ ọdún mélòó ni màmáa bàbáà rẹ? 97 years old

   ______________________________

4. Ọmọ ọdún mélòó ni ìwọ? 19 years old

   ______________________________

5. Ọmọ ọdún mélòó ni ọ̀rẹ́ẹ̀ rẹ? 21 years old

   ______________________________

## Iṣẹ́ Ṣíṣe 2

Dáhùn àwọn ìbéèrè wọ̀nyí ní ẹ̀kúnrẹ́rẹ́.
*Answer the following questions in complete sentences*.

**Bí àpẹẹrẹ:**

Ọmọ ọdún mélòó ni àbúrò rẹ?
Ọmọ ogún ọdún ni àbúrò mi.

Ọmọ ọdún mélòó ni ọmọọ̀ rẹ?
Ọmọ ọdún méjìlélógún ni ọmọọ̀ mi.

1. Ọmọ ọdún mélòó ni bàbáà rẹ?
2. Ọmọ ọdún mélòó ni màmáà rẹ?
3. Ọmọ ọdún mélòó ni bàbáa bàbáà rẹ?
4. Ọmọ ọdún mélòó ni bàbáa màmáà rẹ?
5. Ọmọ ọdún mélòó ni ẹ̀gbọ́n tàbí àbúròò rẹ?

 CC – 2011 The University of Texas at Austin

## Iṣẹ́ Ṣíṣe 3

Dáhùn awọn ìbéèrè wọ̀nyí nípa lílo àpẹẹrẹ tí ó wà ní ìsàlẹ̀ yìí.
*Follow this pattern below to answer the following questions.*

**Bí àpẹẹrẹ:**

Títí--16years old.
Ó jẹ́ ọmọ ọdún mẹ́rìndínlógún.

1. Bàbá àgbà--87 years old
_______________
2. Màmá kékeré--64 years old
_______________
3. Bùrọ̀dá Olú--43 years old
_______________
4. Èmi--17 years old
_______________
5. Bàbáa màmá -- 100 years old
_______________
6. Ọ̀gá Tádé--78 years old
_______________
7. Ìwọ –19 years old
_______________
8. Òun-- 46 years old
_______________
9. Ẹ̀gbọ́n mi ọkùnrin—25 years old
_______________
10. Àbúròò mi obìnrin-- 13 years old
_______________

 CC – 2011 The University of Texas at Austin

## Iṣẹ́ Ṣíṣe 4

Dáhùn awọn ìbéèrè wọ̀nyí nípa lílo àpẹẹrẹ tí ó wà ní ìsàlẹ̀ yìí.
*Follow this pattern below to answer the following questions.*

**Bí àpẹẹrẹ:**

Kóyè--18years old: Ọmọ ọdún méjìdínlógún ni.

1. Ṣadé--46 years old:
2. Bàbá Ẹ̀bùn—50 years old:
3. Wọnúọlá--16 years old:
4. Délé—10 years old:
5. Akin—21 years old:
6. Ìwọ— 18 years old:
7. Ọ̀jọ̀gbọ́nọ̀n rẹ---65 years old:
8. Ọ̀rẹ́ẹ̀ rẹ-- 17 years old:
9. Màmáa bàbáà rẹ--96 years old:
10. John Legend—26 years old:

 CC – 2011 The University of Texas at Austin

## Lesson 4 - Ẹ̀kọ́ Kẹrin:
## Àwọn Àwọ̀ (*Colors*)

There are three primary colors in Yoruba culture:

red (pupa)
black (dúdú)
white (funfun)

**For example:**

| | |
|---|---|
| Ènìyàn dúdú | *A Black person* |
| Ènìyàn funfun | *A White person* |
| Ènìyàn pupa | A light skinned person |

There are other colors besides the primary colors. However, their description is foreign or borrowed.

**For example:**

| | |
|---|---|
| búlúù | *blue* |
| yẹ́lò | *yellow* |
| pîǹkì | *pink* |

However, to describe the colors that are 'off primary colors' such as a light or dark color, we use the words 'díẹ̀' and 'gan-an ni' respectively following the main color.

**For example:**

| | |
|---|---|
| Ó dúdú díẹ̀ | S/he is not very dark |
| Ó pupa gan-an ni | S/he is really light in complexion |




 CC – 2011 The University of Texas at Austin

## Iṣẹ́ Ṣíṣe 1

Ṣe àpéjúwe àwọn ènìyàn wọ̀nyí.
*Describe the following people.*

**Bí àpẹẹrẹ:**

Bill Clinton: Wọ́n funfun

1. Barack Obama:_______________
2. George Clooney:_______________
3. Aretha Franklin:_______________
4. 50 cent:_______________
5. Usher:_______________
6. Jennifer Lopez:_______________
7. Mariah Carey:_______________
8. Halle Berry:_______________
9. Taylor Swift:_______________
10. Miley Cyrus:_______________
11. The Jonas Brothers:_______________
12. The BackStreet Boys:_______________
13. U2:_______________
14. James Brown:_______________
15. Shakira:_______________
16. Madonna:_______________
17. Michael Phelps:_______________
18. Tim Duncan:_______________
19. Michael Jordan:_______________
20. Tina Turner:_______________
21. John Legend:_______________
22. Michelle Obama:_______________
23. Cyndi Lauper:_______________
24. Janet Jackson:_______________
25. Beyoncé:_______________

Another way to describe colors is to use comparison –as and like, **bí** in Yorùbá language.

**For example:**

| | |
|---|---|
| Ó dúdú bí ewé | *S/he/ It is black/dark like a leaf (green color)* |
| Ó dúdú bí èédú | *S/he/ it is dark/black like charcoal* |
| Ó funfun bí eérú | *It is white like ashes (grey)* |

One uses 'bí for colors that are not primary, that is variants of the primary colors.
'Bí i' is used before a noun that starts with a consonant
(bíi gààrí —like gààrí)

Primary colors are also used as the base color to describe variants of colors or other shades of the same color. For example, a beige wall or an off-white wall will be described as 'ogiri funfun' because off-white or beige color is closer to white. Brown color will be described as 'pupa', and blue as in 'blue jeans' will be described as 'dúdú' .

## Iṣẹ́ Ṣíṣe 2

*Group Activity. In pairs, take turns to describe your friend in class.*

 CC – 2011 The University of Texas at Austin



# Chapter 5 - Orí Karùnún | MY FAMILY TREE

## *OBJECTIVES*:

In this chapter you will learn:

- How to describe people by using the verbs 'jẹ́', 'ni'
- How to use the negation 'kọ́'
- How to use the interrogative 'ta ni'
- How to describe one's family

## Àwọn ọ̀rọ̀ (*Vocabulary*)

| Nouns | |
|---|---|
| aáwọ̀ | *differences* |
| àbúrò | *younger sibling* |
| àgbà | *older person* |
| agbolé | *compound* |
| àdúgbò | *neighborhood* |
| àgbàlagbà | *older person* |
| agbẹjọ́rò | *lawyer* |
| àkójọpọ̀ | *collection* |
| akẹ́kọ̀ọ́ | *student* |
| àlàáfíà | *peace* |
| apòògùn | *pharmacist* |
| àpọ́nlé | *respect* |
| ara | *body* |
| àṣà | *culture* |
| baálé | *male head (of family)* |
| burẹ́wà | *ugly* |
| dókítà | *doctor* |
| ẹ̀gbọ́n | *older sibling* |
| ẹ̀kọ́ | *studies* |
| ẹ̀wà | *beans* |
| gbogbo | *all* |
| ìdàgbàsókè | *progress, development* |
| ìdọ̀bálẹ̀ | *prostration* |
| ìdílé | *family (immediate)* |
| ìlú | *town, city, country* |
| ìgbàgbọ́ | *belief* |
| igun | *branch (of family)* |
| ìpàdé | *meeting* |
| ìṣègùn | *medicine* |
| ìtumọ̀ | *the meaning* |
| kódà | *in fact* |

 CC – 2012 The University of Texas at Austin

| | |
|---|---|
| mọ̀lẹ́bí | *family (extended)* |
| ojoojúmọ́ | *every month* |
| ọkọ | *husband* |
| olórí | *head* |
| oṣooṣù | *every month* |
| ọ̀sọ̀ọ̀sẹ̀ | *every week* |
| oúnjẹ | *food* |
| ọjà | *market* |
| ọmọdé | *youth* |
| pàjáwìrì | *emergency* |
| píparí | *settling of; completion of* |
| wúrà | *gold* |

## Noun Phrases

| | |
|---|---|
| bùrọ̀dáa lágbájá | *brother (of somebody)* |
| ètò ẹbí | *organization of family* |

## Verbs

| | |
|---|---|
| dàrú | *confused, disorganized* |
| fún | *for* |
| gbé | *to live in/at* |
| gbọdọ̀ | *must* |
| jẹ | *to eat* |
| jẹ́ | *to be* |
| kúnlẹ̀ | *kneel down* |
| parí | *to complete* |
| sọ̀rọ̀ | *to talk* |
| tí | *if* |
| túmọ̀ sí | *translates to/means/implies* |
| wí pé | *said that* |

## Verb Phrases

| | |
|---|---|
| bí tẹ̀lé | *to be born following* |
| kóra jọ | *to get together* |
| lè dàrú | *can lead to chaos; can be disorganized* |

| | |
|---|---|
| kò ì tí ì | *has/have not yet* |
| máa ń wáyé | *always takes place* |
| lágbára | *to be strong* |
| ṣe kókó | *is important; is crucial* |
| ṣe pàtàkì | *is important* |

## Adjectives

| | |
|---|---|
| ga | *tall* |
| kéré | *small* |
| kúrú | *short* |
| kọ̀ọ̀kan | *each* |
| sanra | *fat* |
| tóbi | *big* |
| tínínrín | *skinny (thin)* |

## Adverbs

| | |
|---|---|
| péré | *only* |

## Conjunction

| | |
|---|---|
| àti | *and* |
| nítorí èyí | *because of this* |
| nítorí pé | *because* |
| nípa | *about* |

## Prepositional phrases

| | |
|---|---|
| láàárín | *among, in the middle of* |
| nígbà mìíràn | *at other times* |

## Interrogative

| | |
|---|---|
| mélòó ni | *how many?* |

## Other Expressions

| | |
|---|---|
| ẹni tí ó bá juni lọ | *anyone that is older than oneself* |
| ìdí èyí ni wí pé | *this/that is why* |
| kí ayé ó gún | *for the world to be in good shape* |
| ọgbọ́n àti òye | *wisdom and understanding* |
| ọ̀kan lára | *one of* |

 CC – 2012 The University of Texas at Austin

## Lesson 1 - Ẹ̀kọ́ Kìíní:
## The verbs ‘jẹ́’ ‘to be’ and ‘ni’ ‘to be’

### The Verb ‘Jẹ́’

The verb **‘jẹ́’** implies *to be*. It is frequently used with professions.

**For example:**

| | |
|---|---|
| Ladi **jẹ́** dókítà. | *Ladi is a doctor.* |
| Fadérera **jẹ́** agbẹjọ́rò. | *Fadérera is an attorney/a lawyer.* |
| Mo **jẹ́** akẹ́kọ̀ọ́. | *I am a student.* |

The verb **jẹ́** can be used to link phrases.

**For example:**

| | |
|---|---|
| Ẹ̀wà **jẹ́** oúnjẹ tí ó dára láti jẹ | *Beans are good to eat.* |

**Jẹ́** can also be used to express one’s age.

**For example:**

| | |
|---|---|
| Kẹ́mi **jẹ́** ọmọ ọdún mẹ́wàá | *Kẹ́mi is 10 years old* |
| Màmáà mi **jẹ́** ọmọ ogójì ọdún | *My mother is 40 years old* |

### Jẹ́ + negation

| | | |
|---|---|---|
| Jẹ́ | → | kì í ṣe |
| Ladi jẹ́ dókítà | → | Ladi kì í ṣe dókítà |
| *Ladi is a doctor* | → | *Ladi is not a doctor* |
| Mo jẹ́ akẹ́kọ̀ọ́ | → | N kì í ṣe akẹ́kọ̀ọ́ |
| *I am a student* | → | *I am not a student* |
| Kẹ́mi jẹ́ ọmọ ọdún mẹ́wàá | → | Kẹ́mi kì í ṣe ọmọ ọdún mẹ́wàá |
| *Kẹ́mi is 10 years old* | → | *Kẹ́mi is not 10 years old* |

 CC – 2012 The University of Texas at Austin

## The verb 'Ni'

In Yorùbá, '**ni**' is another form of the verb 'to be' as used in the sentences below:

| | |
|---|---|
| Èmi ni màmáa Túndé. | *I am Túndé's mother.* |
| Dókítà ni Ládi. | *Ladi is a doctor.* |
| Ọ̀la ni ọjà | *Tomorrow is market day.* |
| Ìyá ni wúrà | *Mother is gold.* |

However, one cannot say:

* Dókítá jẹ́ Ládi
* Ọ̀la jẹ́ ọjà

one would rather say

Ládi jẹ́ dókítá
Ọ̀la jẹ́ ọjọ́ ọjà

## Negation 'kọ́'

When **ni** is negated, it becomes '**kọ́ ni'**, as found in the examples below:

| | |
|---|---|
| Èmi ni bàbáa Kóyè. | *I am Kóyè's father.* |
| Èmi kọ́ ni bàbáa Kóyè. | *I am not Kóyè's father.* |
| Àwọn ni màmáà mi. | *She is my mother.* |
| Àwọn kọ́ ni màmáà mi. | *She is not my mother.* |
| Olú ni àbúrò Adé | *Olú is Adé's younger sibling.* |
| Olú kọ́ ni àbúrò Adé | *Olú is not Adé's younger sibling.* |
| Ṣé àwọn ni olùkọ́ọ̀ rẹ? | *Is s/he your teacher?* |
| Rárá, àwọn kọ́ ni olùkọ́ọ̀ mi. | *No, he is not my teacher.* |

Regular pronouns cannot be used with '**ni**' as in the following examples:

*Mo ni dókítà
*Ó ni olùkọ̀

Similarly, '**kọ́'** cannot be used with regular pronouns as in the following examples:

*Mo kọ́ ni dókítà
*Ó kọ́ ni olùkọ̀


CC – 2012 The University of Texas at Austin

## Iṣẹ́ Ṣíṣe 1

Dáhùn àwọn ìbéèrè wọ̀nyí ní òdì.

*Respond to the following questions negatively.*

1. Ṣé bàbáà rẹ ni olórí ìlú?
   ______________________________
2. Ṣé àwọn ni ẹ̀gbọ́nọn Kíkẹ́?
   ______________________________
3. Ṣé ìwọ ni dókítà?
   ______________________________
4. Ṣé ẹ̀ẹ́jọ àti eéjì ni ẹ̀ẹ́sànán?
   ______________________________
5. Ṣé èmi àti ìwọ ni ẹ̀yin?
   ______________________________

## Iṣẹ́ Ṣíṣe 2

Yí àwọn gbólóhùn yí sí òdì.

*Turn the following into negative.*

1. Bàbáà mi jẹ́ olórí ìlú.
   ______________________________
2. Àwọn ni ẹ̀gbọ́ǹọ̀n mi.
   ______________________________
3. Ó jẹ́ ọlọ́pàá.
   ______________________________
4. Èmi àti iwọ ni ọ̀rẹ́.
   ______________________________
5. Mo jẹ́ agbẹjọ́rò.
   ______________________________

## Iṣẹ́ Ṣíṣe 3

Lo 'jẹ́' tàbí 'ni' láti fi dí àwọn àlàfo wọ̀nyí.
*Use 'jẹ́' or 'ni' to fill out the blank spaces below.*

1. Màmáà mi ______________________ nọ́ọ̀sì.
2. Èmi ______________________ mò ń ṣiṣẹ́ ní ilé-ìwé.
3. Wọ́n ______________________ ọ̀jọ̀gbọ́n ní ilé-ìwèé mi.
4. Ṣé àwọn ______________________ màmáà rẹ?
5. Èmi ______________________ ọmọ bàbáaTádè.
6. Ó màṣe o. Ó ______________________ ọmọdé nií.

## Iṣẹ́ Ṣíṣe 4

Yí àwọn gbólóhùn wọ̀nyí sí òdì.
*Turn the following sentences into negation.*

1. Mo jẹ́ nọ́ọ̀sì ______________________
2. A jẹ́ akẹ́kọ̀ọ́ ______________________
3. O jẹ́ dókítà ______________________
4. Ẹ jẹ́ ọ̀jọ̀gbọ́n ______________________
5. Ó jẹ́ olùkọ́ ______________________
6. Wọ́n jẹ́ olórí ìlú ______________________

 CC – 2012 The University of Texas at Austin

## Lesson 2 - Ẹ̀kọ́ Kejì:

## The interrogative 'Ta ni'

The interrogative '**ta ni**' implies '*who*'

Ta ni ọ̀rẹ́ẹ̀ rẹ?
Ta ni bàbáà rẹ?



### Ìsọ̀rọ̀ngbèsì *(Dialogue)*

| | | |
|---|---|---|
| Ọlá: | Bàbáà mi, mo ní ọ̀rẹ́ kan. | *Dad, I have a friend.* |
| Bàbá Ọlá: | Ìyẹn dára o. Ta ni ọ̀rẹ́ẹ̀ rẹ? | *That's nice. Who is your friend?* |
| Ọlá: | Orúkọ rẹ̀ ni Láńre. | *His name is Láńre.* |
| Bàbá Ọlá: | Ta ni bàbáa Láńre ? | *Who is Láńre's father?* |
| Ọlá: | Ọ̀jọ̀gbọ́n Ọ̀ṣúndáre ni bàbáa Láńre | *Professor Ọ̀ṣúndáre is Láńre's father.* |

### Cultural Vignette: ÀPỌ́NLÉ

Àpọ́nlé jẹ́ ọ̀kan lára àṣà àti iṣé àwọn Yorùbá. Yorùbá máa ǹ pa á lówe pé: ẹni tí ó bá ju 'ni lọ lè juni nù . Ìtumọ̀ èyí ni pé, ẹni tí ó bá ju ènìyàn lọ ní ọgbọ́n àti òye ju ènìyàn lọ. Àwọ́n Yorùbá á tún máa wípé: Àìbọ̀wọ̀ fún àgbà ni kò jẹ́ kí ayé ó gún. Eléyìí túmọ̀ sí pé: ilé ayé ń dàrú nítorí wí pé àwọn ènìyàn kò ṣe àpọ́nlé tí ó yẹ fún àwọn tí ó jù wọ́n lọ.

Bàbá àti ìyá ènìyàn nìkan kọ́ ló yẹ kí ènìyàn ṣe àpọ́nlé fún. Ó ṣe pàtàkì fún gbogbo ènìyàn láti ṣe àpọ́nlé fún ẹ̀gbọ́n, ẹbí, ará àti ojúlùmọ̀ tó bá junì lọ. Ènìyàn kò gbọdọ̀ pe àgbàlagbà lórúkọ. Bùrọ̀dáa lágbájá tàbí àǹtíì/sìsìtáa lágbájá ni ènìyàn gbọdọ̀ pe ẹni tí ó bá junì lọ. Ìdọ̀bálẹ̀ ni ọkùnrin máa ń kí ẹni tí ó bá ju ènìyàn lọ. Àwọn obìnrin máa ń kúnlẹ̀ láti fi àpọ́nlée wọn hàn. Ní ọ̀nà mìíràn, ènìyàn kò gbọdọ̀ lo 'ó' fún ẹni tí ó bá dàgbà ju ènìyàn lọ, kódà kó jẹ́ wí pé ọ̀dún kàn péré ni ẹni náà gbà lọ́wọ́ ènìyàn. Ẹni tí kò bá ní ẹ̀kọ́ ilé ní ó máa ń pe àgbàlagbà lórúkọ. Ara ẹkọ́ ilé ni bí a ti ṣe ń kí àwọ̀n tí ó bá ju ènìyàn lọ.


### Iṣẹ́ Ṣíṣe 1

Dáhùn àwọn ìbéèrè wọ̀nyí ní ẹ̀kúnrẹ́rẹ́.
*Answer the following questions in complete sentences.*

1. Ta ni ó yẹ kí ènìyàn ṣe àpọ́nlé fún?
2. Kí ni àpọ́nlé ní ilẹ̀ẹ Yorùbá?
3. Ta ni ó máa ń pe àgbàlagbà lórúkọ?
4. Kí ni ìtumọ̀ òwe yìí: 'ẹni tí ó bá ju 'ni lọ lè juni nù'?
5. Kí ni àpọ́nlé ní ìlúù rẹ?

 CC – 2012 The University of Texas at Austin

## Lesson 3 - Ẹ̀kọ́ Kẹta:
## Ẹbí ní ìdílé Mẹ́ta (*Three Generations of a Family*)




 CC – 2012 The University of Texas at Austin

## Iṣẹ́ Ṣíṣe 1

Dáhùn àwọn ìbéèrè wọ̀nyí ní ẹ̀kúnrẹ́rẹ́.
*Answer the following questions in complete sentences.*

1. Kí ni orúkọ ìdílée bàbá Àdùkẹ?
2. Kí ni orúkọ bàbáa bàbá Àdùkẹ?
3. Ta ni màmá Àdùkẹ́?
4. Ta ni ọmọ ọmọ Ọlánìkẹ̀ẹ́?
5. Ta ni àwọn ọmọ ọmọ Ọlánìkẹ̀ẹ́?
6. Ọmọ mélòó ni Ọlánìkẹ̀ẹ́ ní?
7. Ọmọ ọmọ mélòó ni Ọlánìkẹ̀ẹ́ ní?
8. Ta ni Babalọlá?
9. Ta ni àbúròo Gbádébọ̀?
10. Ta ni ẹ̀gbọ́n Àdùkẹ́?

 CC – 2012 The University of Texas at Austin

## Iṣẹ́ Ṣíṣe 2

Parí àwọn ọ̀rọ̀ wọ̀nyí.

*Complete the following sentences.*

**Bí àpẹẹrẹ:**

Babalọlá ni ọkọ Títílọlá. Òun ni bàbáa Atinúkẹ́ àti Gbádébọ̀. Òun sì ni ọkọ ọmọ Ọláníkẹ̀ẹ́ àti Adéníyì

1. Adéníyì ni ____________________
2. Gbádébọ̀ ni ____________________
3. Olútóókẹ́ ni ____________________
4. Bádé ni ____________________
5. Atinúkẹ́ ni ____________________

## Iṣẹ́ Ṣíṣe 3

Sọ **lóòótọ́ ni** tàbí **lóòótọ́ kọ́** fún àwọn gbólóhùn wọ̀nyí.

*State whether the following sentences are true or false.*

| | Òótọ́ ni | Òótọ́ kọ́ |
|---|---|---|
| 1. Àdùkẹ́ ni ọkọ Ọláṣùpọ̀. | ☐ | ☐ |
| 2. Ọláṣùpọ̀ ni ìyàwó Àdùkẹ́. | ☐ | ☐ |
| 3. Atinúkẹ́ ni ọmọ ọmọ Ọláníkẹ̀ẹ́. | ☐ | ☐ |
| 4. Bádé ni bàbá Atinúkẹ́. | ☐ | ☐ |
| 5. Adéníyì ni bàbáa bàbáa Gbádébọ̀. | ☐ | ☐ |
| 6. Babalọlá ni bàbáa Gbádébọ̀. | ☐ | ☐ |
| 7. Olútóókẹ́ ni ẹ̀gbọ́nọn Títílọlá. | ☐ | ☐ |
| 8. Ọláníkẹ̀ẹ́ ni ìyàwó Adéníyì. | ☐ | ☐ |
| 9. Ọláṣùpọ̀ ni ọmọọ Bádé. | ☐ | ☐ |
| 10. Bádé àti Títí ni àwọn ọmọ Adéníyì àti Ọláníkẹ̀ẹ́. | ☐ | ☐ |

 CC – 2012 The University of Texas at Austin

## Iṣẹ́ Ṣíṣe 4

Dáhùn àwọn ìbéèrè wọ̀nyí.
*Answer the following questions*.

**Bí àpẹẹrẹ:**

Ọkọ Títílọlá ni? Babalọlá

1. Bàbáa bàbá Àdùkẹ́ ni?
2. Òbí Àdùkẹ́ àti Ọláṣùpọ̀ ni?
3. Bàbáa Bádé ni?
4. Ọmọọ Bádé ni?
5. Ọmọọ Babalọlá àti Títílọlá ni?

 CC – 2012 The University of Texas at Austin

Wá àwọn ọ̀rọ̀ wọ̀nyí.

*Look for these words in the puzzle below. Pay attention to the tones!*

**àpọ́nlé, àṣà, àgbàlagbà, bùrọ̀dá, ọgbọ́n, ìdọ̀bálẹ̀, wúrà, ìdílé, olórí, ìdàgbàsókè**

| | | | | | | | | | | | | | | |
|---|---|---|---|---|---|---|---|---|---|---|---|---|---|---|
| à | g | b | a | l | a | d | à | b | á | d | í | l | é | à |
| d | ì | l | e | l | o | b | í | ṣ | ọ | l | a | ó | g | l |
| w | í | d | á | g | b | á | s | d | à | l | e | l | a | a |
| d | ú | k | í | ó | b | à | ó | k | ọ̀ | í | k | o | l | ọ |
| w | u | r | á | l | e | a | g | í | b | ọ | a | l | a | g |
| ó | t | b | à | í | é | d | á | b | ọ̀ | á | g | á | m | b |
| ì | g | i | d | ọ̀ | b | à | d | g | à | í | j | b | n | o |
| á | d | d | ọ̀ | o | d | í | p | o | k | l | b | a | ọ́ | l |
| k | í | ọ̀ | g | l | b | ó | d | ọ́ | l | b | à | b | k | n |
| o | g | a | b | i | t | ù | s | a | n | í | n | g | á | b |
| ó | l | o | r | á | í | n | r | á | b | l | d | ó | b | a |
| a | d | ó | s | á | l | ọ̀ | b | ọ̀ | r | d | é | k | i | à |
| ọ̀ | k | o | r | ó | b | ẹ̀ | l | á | d | í | l | a | r | i |
| a | d | á | b | í | o | d | ó | b | i | á | g | d | í | b |
| b | Ì | d | à | g | b | à | s | ó | k | è | í | k | e | à |

 CC – 2012 The University of Texas at Austin

## Cultural Vignette: Ẹbí ní ilẹ̀ẹ Yorùbá

Ní ilẹ̀ẹ Yorùbá, mọ̀lẹ́bí jẹ́ àkójọpọ̀ àpapọ̀ igun. Baálé ilé ni olórí igun kọ̀ọ̀kan. Ẹ̀tò ẹbí jẹ́ nǹkan tí ó ṣe pàtàkì fún àlàáfíà láàárín àwọn ọmọ ẹbí àti ìlú lápapọ̀. Ìdí èyí ni wí pé, àlàáfíà láàárín mọlẹ́bí ṣe kókó fún ìdàgbàsókè ìlú. Yorùbá ní ìgbàgbọ́ wí pé ìlé lè dàrú tí àlàáfíà kò bá sí láàárínin mọlẹ́bí. Gbogbo ènìyàn ni ó gbọ́dọ̀ jẹ́ mọlẹ́bí kan tàbí òmíràn. Nítorí èyí ni Yorùbá fi máa ń sọ wí pé: "A kìí wáyé ká má lẹ́bí." Ìpàdée mọlẹ́bí máa ń wáyé ní ọ̀sọ̀ọ̀sẹ̀ tàbí ní oṣooṣù. Nígbà mìíràn, àwọn mọlẹ́bí máà ń ní ìpàdé pàjáwìrì. Gbogbo mọlẹ́bí tún máa ń kóra jọ láti ṣe ìgbéyàwó, ìsọmọlórúkọ àti ìjádeòkù.

Gbogbo ẹbí ni ó ní olórí ẹbí. Olórí ẹbí jẹ́ ọkùnrin tí ó dàgbà jùlọ nínúu mọlẹ́bí. Ṣùgbọ́n nígbà mìíràn olórí ẹbí lè jẹ́ obìnrin tí ó dàgbà jùlọ nínúu mọlẹ́bí. Ara àwọn ojúṣe olórí ẹbí ni pípárí aáwọ̀ láàárín àwọn mọlẹ́bí. Olórí ẹbí tún máa ń ṣojú àwọn mọlẹ́bíi rẹ̀ ní ìpàdé àdúgbò, ìpàdé agbolé, tàbí ìpàdé ìlú. Ó ṣe pàtàkì kí olórí ẹbí rí i wí pé ẹbí kò tú mọ́ òun lórí. Ìdàgbàsókè ẹbí ní í ṣe pẹ̀lú irú olórí ẹbí tí wọ́n bá á ní.

### Iṣẹ́ Ṣíṣe 6

Dáhùn àwọn ìbéèrè wọ̀nyí ní ẹ̀kúnrẹ́rẹ́.
*Answer the following questions in complete sentences.*

1. Kí ni pàtàkì mọ̀lẹ́bí ní ilẹ̀ẹ Yorùbá?
   ______________________________
2. Ta ni olórí ẹbí ní ilẹ̀ẹ Yorùbá?
   ______________________________
3. Kí ni iṣẹ́ olórí ẹbí nínú ẹbí àti ní ìlú?
   ______________________________
4. Kí ni mọlẹ́bí jẹ́ fún ìdàgbàsókè ìlú?
   ______________________________
5. Kí ni ìtumọ̀ọ mọlẹ́bí?
   ______________________________

 CC – 2012 The University of Texas at Austin

**Iṣẹ́ Ṣíṣe 7**

Túmọ̀ àwọn ọ̀rọ̀ wọ̀nyí ni èdèe Yorùbá.
*Provide the meanings of the following words in Yorùbá Language.*

1. olórí ____________________
2. Ìpàdé ____________________
3. gbọ́dọ̀ ____________________
4. ojúṣe ____________________
5. baálé ilé ____________________




### Ọ̀rọ̀ àdásọ *(Monologue)*

Àbíkẹ́ ń sọ̀rọ̀ nìpa ẹbíi rẹ̀ fún Arábìnrin Fáladé, olùkọ́ọ rẹ̀.
*Àbíkẹ́ is talking about her family to Mrs. Fáladé, her teacher.*

### Ẹbí mi (*My Family*)

Ẹbí mi ni ẹbí Adédìran
À ń gbé ní ìlú Ìbàdàn ní àdúgbò Ìyágànkú. Bàbá àti ìyáà mi bí ọmọ mẹ́rin. Àkọ́bí wọn ń jẹ́ Adéolú. Ọmọ ọdún méjìlélọ́gbọ̀n ni wọ́n. Apòògùn sì ni wọ́n pẹ̀lú. Wọ́n ní ìyàwó. Orùkọ ìyàwóo wọn ni Gbémi. Wọ́n bí ọmọ méjì, Doyin àti Yétúndé. Ọkùnrin ni Doyin. Doyín jẹ́ ọmọ ọdún mẹ́rin. Yétúndé sì jẹ́ ọmọ ọdún méjì. Ọmọ kejì tí bàbáà àti màmáà mi bí ni Bímpé. Bímpé jẹ́ ọmọ ọgbọ̀n ọdún. Dókítà ni wọ́n, ṣùgbọ́n wọ́n kò ì tí ì fẹ́ ọkọ. Ẹni tí ó tẹ̀lé Bímpé ni Jídé. Ọmọ ọdún mẹ́rìndínlọ́gbọ̀n ni wọ́n. Agbẹjọ́rò ni wọ́n. Wọ́n ṣẹ̀ṣẹ̀ bí ọmọ kan tí orúkọ rẹ̀ ń jẹ́ Rónkẹ́. Rónkẹ́ jẹ́ ọmọ oṣù mẹ́ta. Èmi ni àbígbẹ̀yìn nínú ẹbí mi. Orùkọọ̀ mi ni Àbíkẹ́. Mo jẹ́ ọmọ ọdún méjìlélógún. Mo wà ní Yunifásítì ti ìlú Ìbàdàn. Mo ń kọ́ nípa ẹ̀kọ́ ìṣègùn.

 CC – 2012 The University of Texas at Austin

## Iṣẹ́ Ṣíṣe 8

Dáhùn àwọn ìbéèrè wọ̀nyí.
*Respond to the following questions.*

1. Kí ni orúkọ ẹni tí ó ń sọ̀rọ̀?

   ______________________________

2. Kí ni iṣẹ́ tí Bímpé ń ṣe?

   ______________________________

3. Ipò wo ni Adéolú wà nínú ẹbí yìí?

   ______________________________

4. Kí ni orúkọ àdúgbò àwọn Àbíkẹ́?

   ______________________________

5. Kí ni orúkọ ìyàwó Adéolú?

   ______________________________

6. Ta ni wọ́n bí tẹ̀lé Bímpé?

   ______________________________

7. Ọmọ ọdún mélòó ni Jídé?

   ______________________________

8. Kí ni orúkọ àwọn ọmọ Adéolú?

   ______________________________

9. Kí ni orúkọ ilé-ìwé gíga Àbíkẹ́?

   ______________________________

10. Kí ni orúkọ ẹbí yìí?

   ______________________________

 CC – 2012 The University of Texas at Austin

## Iṣẹ́ Ṣíṣe 9

Parí àwọn ọ̀rọ̀ wọ̀nyí.
*Complete the following based on the monologue.*

**Bí àpẹẹrẹ:**

Ọmọ ọdún méjìlélógún ni = Àbíkẹ́

1. Apòògùn ni = ________
2. Ìyàwó Adéolú ni = ________
3. Doyin àti Yétúndé ni = ________
4. Ọmọ kejìi bàbáà àti màmáà mi ni = ________
5. Ọmọ ọdún mẹ́rin ni = ________
6. Ọmọ ọdún méjì ni = ________
7. Ọmọ ọgbọ̀n ọdún ni = ________
8. Dókítà ni = ________
9. Ó ń kọ́ nípa ẹ̀kọ́ ìṣègùn = ________
10. Ọmọ ọṣù mẹ́ta ni = ________
11. Àbígbẹ̀yìn ni = ________
12. Agbẹjẹ́rò ni = ________
13. Ọmọ ọdún mẹ́rìndínlọ́gbọ̀n ni = ________
14. Ọmọ Yunifásítì ni = ________
15. Ó ń sọ̀rọ̀ nìpa ẹbíi rẹ̀ = ________





### Ọ̀rọ̀ àdáṣọ *(Monologue)*

**Ẹbí Akínwálé**

Orúkọ mi ni Lọlá. Orúkọ bàbáà mi ni Fẹ́mi. Orúkọ màmáà mi ni Ọláníkẹ̀ẹ́. Mo ní abúrò mẹ́ta. Orúkọ wọn ni Jídé, Báyọ̀ àti Bùnmi. Jídé àti Báyọ̀ ni àwọn abúrò mi ọkùnrin, Bùnmi sì ni àbúrò mi obìnrín. Jídé ni ọmọ kejì. Báyọ̀ ni ọmọ kẹta. Bunmi ni àbúrò mi àbígbẹ̀yìn. À ń gbé ní ìlú Èkó. Mo fẹ́ràn̄an gbogbo àwọn ẹbîi mi gan-an ni.

 CC – 2012 The University of Texas at Austin




**Iṣẹ́ Ṣíṣe 10**

Dáhùn àwọn ìbéèrè wọ̀nyí ní ẹ̀kúnrẹ́rẹ́.
*Answer the following questions in complete sentences.*

1. Kí ni orúkọ ẹbíi Lọlá?__________
2. Kí ni orúkọọ bàbáa Jídé?__________
3. Ta ni Báyọ̀?__________
4. Kí ni orúkọ àwọn àbúròo Lọlá?__________
5. Ta ni Ọláníkẹ̀ẹ́ ?__________
6. Kí ni orúkọ ẹ̀gbọ́nọn Lọlá?__________
7. Ta ni Bùnmi?__________
8. Ọmọ mélòó ni ó wà nínú ẹbí Akínwálé?__________

 CC – 2012 The University of Texas at Austin

## Iṣẹ́ Ṣíṣe 11

Mú èyí tí ó bá tọ̀nà nínú àwọn ìdáhùn wọ̀nyí.
*Circle the correct answer.*

1. Orúkọ bàbáa Lọlá ni?
a. Gbénga
b. Fẹ́mi
c. Báyọ̀
d. Ṣeun

2. Kí ni orúkọ àbúròo Bàyọ́?
a. Lọlá
b. Bùnmi
c. Kẹ́mi
d. Jídé

3. Ọmọ mélòó ni Ọláníkẹ̀ẹ́ bí?
a. Ọmọ mẹ́ta
b. Ọmọ márùnún
c. Ọmọ kan
d. Ọmọ mẹ́rin

4. Ẹ̀gbọ́n mélòó ni Bùnmi ní?
a. Méjì
b. Mẹ́ta
c. Mẹ́fà
d. Mẹ́rin

5. Ìlú wo ni ẹbí Akínwálé ń gbé?
a. Ìbàdàn
b. Abẹ́òkúta
c. Èkó
d. Ilé-Ifẹ̀

 CC – 2012 The University of Texas at Austin

## Iṣẹ́ Ṣíṣe 12

Túmọ̀ àwọn ọ̀rọ̀ wọ̀nyí ni èdèe Yorùbá.

*Provide the meanings of the following words in Yorùbá language.*

1. My brother-in-law
2. Her mother-in-law
3. His niece
4. Your nephew
5. My first cousin
6. Our uncle
7. Your aunt
8. My grandfather
9. Their great grandfather
10. Her grandmother

## Iṣẹ́ Ṣíṣe 13

So àwọn tí ó bara mu ni ọ̀wọ́ A àti ọ̀wọ́ B papọ̀.

*Match the words in column A with those in column B.*

| A | B |
|---|---|
| Ẹbí | Younger sibling |
| Bàbá | Older sibling |
| Màmá | Grandmother |
| Bàbáa bàbá | Grandfather |
| Màmáa màmá | Mother |
| Ẹ̀gbọ́n | Father |
| Àbúrò | Family |

 CC – 2012 The University of Texas at Austin

## Iṣẹ́ Ṣíṣe 14

So àwọn tí ó bara mu ni ọ̀wọ́ A àti ọ̀wọ́ B papọ̀.

*Match the words in column A with those in column B.*

| A | B |
|---|---|
| Ìkúnlẹ̀ | Respect |
| Ìdọ̀bálẹ̀ | Culture |
| Àpọ́nlé | Compound |
| Àṣà | Kneeling down |
| Agbolé | Prostration |

## Iṣẹ́ Ṣíṣe 15

Ya àwòrán ẹbí rẹ. Tí o bá ṣe é ṣe, ya àwòrán yìí títí dé ìran kẹta.

*Draw a picture of your family, if possible a three- generation family tree.*

1. Generation

2. Generation

3. Generation


CC – 2012 The University of Texas at Austin

### Iṣẹ́ Ṣíṣe 16

Mú fọ́tò ẹbí rẹ wá sí kíláàsì. Fi fọ́tò ẹbí rẹ han ọ̀rẹ́ẹ̀ rẹ, jẹ́ kí ọ̀rẹ́ẹ̀ rẹ gbìyànjú bóyá ó lè sọ nípa àwọn ẹbí rẹ fún ẹ.

*Bring a picture of your family to class. Show it to your partner in class, and let your partner guess who the members of your family are.*

### Iṣẹ́ Ṣíṣe 17 Ní méjì méjì. (*In pairs)*


Nínúu kíláàsì, láláìsí fọ́tò, ṣe àpèjúwe ẹbí rẹ fún ọ̀rẹ́ẹ̀ rẹ, kí ọ̀rẹ́ẹ̀ rẹ náà sì ṣe àpèjúwe ẹbíi rẹ̀ fún ìwọ náà. Ẹ kọ ohun tí ẹ sọ fún ara yín sílẹ̀.


*In pairs, without pictures, let each student describe his or her family to his or her partner*. Each of you should write down what the other person said.


CC – 2012 The University of Texas at Austin


## Lesson 4 - Ẹ̀kọ́ Kẹrin:
## Describing people

| | |
|---|---|
| Àbúròò mi ọkùnrin lágbára | *My younger brother is strong* |
| Ọ̀rẹ́ẹ̀ mi sanra | *My friend is fat* |
| Mo kúrú | *I am short* |
| Tádé ga | *Tádé is tall* |
| | |
| Ẹ̀gbọ́nọ̀n mi tínínrín | *My older sibling is skinny* |
| Bàbáà mi kúrú | *My father is short* |
| Ọ̀rẹ́ẹ̀ mi tóbi | *My friend is big* |
| Kò kúrú kò ga | *S/he is neither tall nor short* |
| | |
| Ènìyàn dúdú | *a black person* |
| Ènìyàn pupa | *a light-skinned person* |
| Ènìyàn funfun | *a white person* |



Abíọ́lá nìyí. Ó sanra. Kò ga. Òṣìṣẹ́ ni.


Sẹ̀indè nìyí. Ó tínínrín. Ó ga. Ó yọ̀lẹ.


CC – 2012 The University of Texas at Austin



Kúnlé nìyí. Ó tóbi. Ó lágbára.
Akínkanjú ènìyàn ni.



Títí nìyí. Kò kúrú. Kò ga.

Gerunds are formed from adjectival verbs.
Some examples of adjectival verbs include ga (tall), sanra (fat) and tóbi (big).

| | | |
|---|---|---|
| ga | → | gíga |
| sanra | → | sísanra |
| tóbi | → | títóbi |

However, some adjectival verbs do not follow the above structure.

Some examples include:

| | | | |
|---|---|---|---|
| kéré | → | kékeré | *small* |
| kúrú | → | kúkúrú | *short* |
| burú | → | búburú | *wicked, mean* |

Gerunds can be used to describe people. They follow their nouns.

**For example:**

màmáà mi jẹ́ ènìyàn gíga *my mother is a tall person*

OR

ènìyàn sísanra ni bàbáà mi *my father is a fat person*

 CC – 2012 The University of Texas at Austin

The prefixes oní-, al-, ọl-, ẹl- (*one who is* ) can be added to the noun to describe people.

**For example:**

ọgbọ́n → ọlọ́gbọ́n
àànú → aláàánú
ìwàpẹ̀lẹ́ → oníwàpẹ̀lẹ́

**Example:**

màmáà mi jẹ́ ọlọ́gbọ́n

OR
màmáà mi jẹ́ ọlọ́gbọ́n ènìyàn

OR
ọlọ́gbọ́n ènìyàn ni màmáà mi




## Ọ̀rọ̀ àdáṣọ *(Monologue)*

Olú ń ṣe àpèjúwe ẹbí rẹ̀ nínúu kíláàsì.
*Olú is describing his family in the classroom.*

Bàbáà mi tínínrín, wọ́n sì dúdú. Màmáà mi sanra, wọ́n sì pupa. Wọ́n lẹ́wà. Kì í ṣe pé bàbáà mi búrẹ́wà o! Wọ́n jẹ́ ọlọ́gbọ́n, aláàánú àti onírẹ̀lẹ̀. Wọ́n sì tún jẹ́ ènìyàn gíga. Màmáà mi jẹ́ oníwàpẹ̀lẹ́. Wọn kì í ṣe onígbéraga. Wọn kò ga bíi bàbáà mi. Wọn kò sì kúrú púpọ̀. Wọ́n jẹ́ ènìyàn rere. Wọ́n sì jẹ́ ọmọlúwàbí ènìyàn.

### Iṣẹ́ Ṣíṣe 1

Sọ lóòótọ́ ni tàbí lóòótọ́ **kọ́** fún àwọn gbólóhùn wọ̀nyí.
*State whether the following sentences are true or false.*

| | Òótọ́ ni | Òótọ́ kọ́ |
|---|---|---|
| 1. Bàbá Olú sanra. | ☐ | ☐ |
| 2. Màmá Olú ga. | ☐ | ☐ |
| 3. Bàbá Olú jẹ́ oníwàpẹ̀lẹ́. | ☐ | ☐ |
| 4. Bàbá Olú kò búrẹ́wà. | ☐ | ☐ |
| 5. Màmá Olú kò gbéraga. | ☐ | ☐ |

## Iṣẹ́ Ṣíṣe 2

Ṣe àpèjúwe àwọn ènìyàn wọ̀nyí.
*Describe the following people.*

**Bí àpẹẹrẹ:**

Britney Spears = Ó kúrú, ó kéré, kò gbéraga.

1. George H. W. Bush = ____________________
2. Miley Cyrus = ____________________
3. 50 Cent = ____________________
4. Barack Obama = ____________________
5. Michael Jackson = ____________________
6. Michael Phelps = ____________________
7. Bill Clinton = ____________________
8. Hillary Clinton = ____________________
9. Carrie Underwood = ____________________
10. Michelle Obama = ____________________
11. Kanye West = ____________________
12. Oprah Winfrey = ____________________
13. Will Smith = ____________________
14. Paula Abdul = ____________________
15. Simon Cowell = ____________________
16. Christina Aguilera = ____________________
17. Angelina Jolie = ____________________
18. Brad Pitt = ____________________
19. Jennifer Aniston = ____________________
20. Nelson Mandela = ____________________
21. Dolly Parton = ____________________
22. Percy Sledge = ____________________
23. Beyoncé Knowles = ____________________
24. King Sunny Ade = ____________________
25. Fela Anikulapo Kuti = ____________________
26. Jennifer Aniston = ____________________
27. Denzel Washington = ____________________
28. Dalai Lama = ____________________
29. Muhammed Ali = ____________________
30. Martin Luther King Jr. = ____________________



# Chapter 6 - Orí Kẹ́fà | SHOP WITH ME

## ***OBJECTIVES:***

In this chapter you will learn:

- The use of the interrogative 'Eélòó
- Oní-/Al-/Ẹl- /Ọl-
- How to haggle
- Numbers 100-3000

## Àwọn ọ̀rọ̀ (*Vocabulary*)

| Nouns | |
|---|---|
| aago | *clock/bell* |
| àgbàdo | *corn* |
| àgbẹ̀ | *farmer* |
| àgbò | *ram* |
| àlùbọ́sà | *onion* |
| àmàlà | *yam floured meal* |
| aṣọ | *cloth/clothing* |
| ayò | *a game* |
| ewúrẹ́ | *goat* |
| fìlà | *hat* |
| gàárí | *grain made from cassava* |
| ìjọ̀gbọ̀n | *trouble* |
| ilá | *okra/okro* |
| ìpolówó | *advertisement* |
| Ìrìn-àjò | *journey* |
| irú | *locust bean* |
| kẹ̀kẹ́ | *bicycle* |
| olóko | *farm owner* |
| òróró | *peanut oil/vegetable oil* |
| oúnjẹ | *food* |
| ọ̀gẹ̀dẹ̀ | *plantain* |
| ọjà | *market* |
| ọjọ́ | *day* |
| ọkà / àmàlà | *meal made from yam flour* |
| ọ̀la | *tomorrow* |
| ọlọ́jọ́ | *periodic* |
| màálù | *cow* |
| méje-méje | *in sevens* |
| sùúrù | *peace* |
| wòsìwósì | *petty trading* |

 CC – 2012 The University of Texas at Austin

## Noun Phrases

| | |
|---|---|
| àwọn ọjà kan | *some markets* |
| èlò ilé | *household items* |
| ẹ̀kọ mímu | *pap* |
| erè oko | *farm produce* |
| ẹ̀yà ọkọ̀ | *car parts* |
| ìyá aláta | *female pepper seller* |
| ọjà oko | *farm market/ village market* |

## Adjective

| | |
|---|---|
| tuntun | *new* |

## Other Expressions

| | |
|---|---|
| ó súnmọ́ | *It's near* |

 CC – 2012 The University of Texas at Austin

## Lesson 1 - Ẹ̀kọ́ Kìíní:

## Interrogative: Eélòó

Interrogative **'Eélòó'** implies *'how much'*. For example:

| | | |
|---|---|---|
| **Buyer:** | Eélòó ni ata yìí? | *How much is this pepper?* |
| **Seller:** | Ogúnun náírà ni. | *It is twenty naira (₦20).* |

### Iṣẹ́ Ṣíṣe 1

Lo àpẹẹrẹ tí ò wà ní ìsàlẹ̀ yìí láti fi dáhùn àwọn ìbéèrè wọ̀nyí.
*Use the model below to answer the following questions.*

**Bí àpẹẹrẹ:**

Hat (₦ 50)

Eélòó ni fìlà yìí?
Àádọ́ta náírà ni.

1. Shoe (₦ 70)
2. Pen (₦ 40)
3. Bag (₦ 65)
4. Onion (₦ 12)
5. Corn (₦ 20)
6. Hat (₦ 35)
7. Plantain (₦ 25)
8. Mango (₦ 18)
9. Okra (₦ 22)
10. Locust beans (₦ 15)

 CC – 2012 The University of Texas at Austin

## Iṣẹ́ Ṣíṣe 2 Nínà ọjà *Haggling*

Lo àpẹẹrẹ tí ò wà ní ìsàlẹ̀ yìí láti fi dáhùn àwọn ìbéèrè wọ̀nyí.
*Use the model below to answer the following questions.*

**Bí àpẹẹrẹ:**

A pair of pants (₦ 50)

Ṣé ṣòkòtò náà gba ogójì náírà?
Rárá, kò gbà.

1. Shoe (₦ 70)
2. Dress (₦ 40)
3. Beans (₦ 15)
4. Onion (₦ 5)
5. Corn (₦ 8)
6. Banana (₦ 10)
7. Plantain (₦ 25)
8. Dictionary (₦ 49)
9. Okra (₦ 20)
10. Spinach (₦ 17)

## Iṣẹ́ Ṣíṣe 3

Wo àpẹẹrẹ tó wà lókè yìí, kọ ìsọ̀rọ̀ǹgbèsì tí ó wáyé láàárin ìwọ àti ìyá ọlọ́jà sílẹ̀. Má ṣe jẹ́ kí ó ju gbólóhùn mẹ́wàá lọ.
*Use the example above; write ten lines of dialogue between you and a market woman (haggling in the market).*

## Lesson 2 - Ẹ̀kọ́ Kejì:
## Oní-/Al-/Ẹl-/Ọl-

Al-/Ẹl /Ọl- are prefixes used to describe one who owns, one who does, one who sells, or one who has. They are derivatives of Oní-/. For example, oní + aṣọ —> onáṣọ—> aláṣọ. n=l because they are allophones, and /i/ is elided with tone retention. The initial vowel /o/ takes the form of /a/ which is then copied. Note that al-, ọl-, ẹl-, and el- are allomorphs of oní

For example:

| | | | | | |
|---|---|---|---|---|---|
| oní | + | ata | → | aláta | *one who sells peppers* |
| oní | + | ọmọ | → | ọlọ́mọ | *one who has a child* |
| oní | + | ẹran | → | ẹlẹ́ran | *one who sells meat* |
| oní | + | iṣu | → | oníṣu | *one who sells yams* |
| oní | + | aago | → | aláago | *one who sells or fixes watches* |

Note the initial vowel copying in aláta, ọlọ́mọ, ẹlẹ́ran, and aláago.

 CC – 2012 The University of Texas at Austin

## Iṣẹ́ Ṣíṣe 1

Use oní-, al-, ẹl-, or ọl-

1. àmàlà = ____________________
2. gààrí = ____________________
3. irú = ____________________
4. àlùbọ́sà = ____________________
5. kẹ̀kẹ́ = ____________________
6. wòsìwósì = ____________________
7. ilá = ____________________
8. aṣọ = ____________________
9. òróró = ____________________
10. aago = ____________________
11. ọkà = ____________________
12. ọlá = ____________________
13. ayò = ____________________
14. fìlà = ____________________
15. sùúrù = ____________________

## Iṣẹ́ Ṣíṣe 2

Fi èyí tó bá yẹ dí àwọn àlàfo wọ̀nyí

*Fill in the spaces below with the appropriate words using oní-, al-, ẹl-, or ọl-*

Ní ọjọ́ kan, mo lọ sí ọjà láti lọ ra aṣọ lọ́wọ́ ____________. Ní ibi tí mo ti ń bá ____________ sọ̀rọ̀ lọ́wọ́ ni mo ti rí ____________. Mo pè é, mo sì ra iṣu mẹta lọ́wọ́ _______ láti fi gún iyán. Bí mo ṣe fẹ́ máa lọ ni mo tún rí ____________ àti ____________ tí wọ́n ń polówó ata àti ẹran. Mo pe àwọn náà, mo sì ra ata àti ẹran pẹ̀lú.

 CC – 2012 The University of Texas at Austin

# Lesson 3 - Ẹ̀kọ́ Kẹta:
# Nínà Ọjà (*Haggling)*




## Ìsọ̀rọ̀ngbèsì *(Dialogue)*

**Nínú ọjà (*Inside the market*)**



Ìyá aláta àti oníbàárà
*Pepper seller and a buyer*

| | |
|---|---|
| **Màmáa Tádé:** | Eélòó ni tàtàsée yín, ìyá aláta? |
| **Ìyá Aláta:** | Èwo nínúu wọn? |
| **Màmáa Tádé:** | Àwọn tí ó wà ni ààrín yẹn? |
| **Ìyá Aláta:** | Náírà márùnún ni àwọn yẹn. |
| **Màmáa Tádé:** | Háà! Wọ́n ti wọ́n jù. N kò lè san náírà márùnún o. Ẹ jẹ́ kí n san náírà mẹ́ta àbọ̀. |
| **Ìyá Aláta:** | Rárá, kò gbà. (Màmáa Tádé ń lọ.) Ó dára o. Ẹ wá mú u ní náírà mẹ́ta àbọ̀. |
| **Màmáa Táde:** | Ẹ gbà. Náírà márùnún nìyí o. |
| **Ìyá Aláta:** | Ò dára o. Ẹ gba náírà kan àti àádọ́ta kọ́bọ̀. Ẹ padà wá o. |

**Màmáa Táde:** Mo gbọ́ o.

## Iṣẹ́ Ṣíṣe 1

Dáhùn àwọn ìbéèrè wọ̀nyí ní ẹ̀kúnrẹ́rẹ́.
*Answer the following questions in complete sentences.*

1. Ìbéèrè wo ni màmáa Tádé bèèrè lọ́wọ́ ìyá aláta?
2. Eélòó ni ìyá aláta pe tàtàsé fún màmáa Tádé?
3. Eélòó ni màmáa Tádé ní òun máa san?
4. Eélòó ni màmáa Tádé san ní ìgbẹ̀yìn?
5. Ṣéńjì eélòó ni ìyá aláta fún màmáa Tádé?

## Cultural vignette: ỌJÀ

Ọjà jẹ́ ibi tí àwọn ènìyàn tí ń tà tàbí tí wọ́n ti ń ra nǹkan. Àwọn ọjà kan wà fún nńkan pàtó tí ènìyan bá fẹ́. Bí àpẹẹrẹ, ọjà oúnjẹ yàtọ̀ sí ọjà aṣọ. Bẹ́ẹ̀ ni ọjà aṣọ yàátọ̀ sí ọjà ohun èlò ilé. Oríṣiríṣi ọjà ni ó wà ní ilẹ̀ẹ Yorùbá. Ní ìlù Ìbàdàn, ọjà tí ó wà fún aṣọ títà ni Ọjàa Gbági tuntun àti Ọjà Alẹ́ṣinlọ́yẹ́. Ọjà Òjé, Ọjà Orítamẹ́rin àti Ọjàa Bódìjà ni wọn ti máa ń ta nǹkan bíi oúnjẹ àti ohun èlò ilé. Ọjàa Géètì ni wọn ti máa ń ta àwọn ẹ̀yà ọkọ̀. Ọjàa Mónìyà àti Ọjà Ọ̀ránỵàn ni ibi tí wọ́n ti máá ń ta ẹran ìso bíi àgbò, ewúrẹ́ àti màálù.

Àwọn ọjà mìíràn wà tí kì í ṣe olójoojúmọ́. Nígbà mìíràn, ó lè jẹ́ ọjà ọlọ́jọ́ mẹ́ta-mẹ́ta, márùnún-márùnún tàbí méje-méje. Ọja oko ni àwọn ọja tí ó súnmọ oko tí àwọn àgbẹ̀ ti máa ń ko irè oko wọn wá fún títà.

## Iṣẹ́ Ṣíṣe 2

Dáhùn àwọn ìbéèrè wọ̀nyí.
*Answer the following questions.*

1. Irú àwọn ọjà wo ni ó wà ní ilẹ̀ẹ Yorùbá?
2. Dárúkọ àwọn ọjà ìlú Ibàdàn tí a kà nínú àyọkà yìí.
3. Àwọn ọjà wo ni wọ́n ti ń ta aṣọ ní ìlú Ìbàdàn?
4. Kí ni wọ́n ń ta ọjà ni Ọjàa Mọ́níyà àti Ọjà Ọ̀ránỵàn?
5. Ọjọ́ mélòó – mélòó ni wọ́n sáábà máa ń ná àwọn ọjà ìyókù?

 CC – 2012 The University of Texas at Austin

**Iṣẹ́ Ṣíṣe 3**

Jẹ́ ká ṣe àfiwé àṣà. Sọ fún wa nípa àṣà ọjà ní ìlúù rẹ.

*Tell us about the market system in your country.*

## Ìsọ̀rọ̀ngbèsì *(Dialogue)*



Màmáa Ṣadé àti Màmáa Fúnmi pàdé ní ọjà.

*Ṣadé's mom and Fúnmi's mom meet in the market.*

| | |
|---|---|
| **Màmáa Ṣadé:** | Ẹ káàárọ̀ o, Màmáa Fúnmi |
| **Màmáa Fúnmi:** | Ẹ káàárọ̀ o, Màmáa Ṣadé, a à jí bí? |
| **Màmáa Ṣadé:** | A jíire o. Gbogbo ilé ńkọ́? |
| **Màmáa Fúnmi:** | A dúpẹ́ o. Dáadáà ni wọ́n wà. Bàbáa Ṣadé ńkọ́? Ṣé àlàáfíà ni wọ́n wà? |
| **Màmáa Ṣadé:** | A dúpẹ́ o. Bàbáa Fúnmi náà ńkọ́ o? |
| **Màmáa Fúnmi:** | Wọ́n wà o. Wọ́n mà ti lọ sí ìrìn àjò. |
| **Màmáa Ṣadé:** | Dáadáa ni wọn yóò dé o. Mo mà fẹ́ ra ata rodo, ata ṣọ̀ǹbọ̀, tòmáàtì, àlùbọ́sà, iyọ̀ àti epo pupa. |
| **Màmáa Fúnmi:** | Èmi náà fẹ́ ra ẹja tútù àti ṣọ̀ǹbọ̀ fún ọbẹ̀ ẹja aláta ni. |
| **Màmáa Ṣadé:** | Mo máa ra ẹ̀fọ́ọ ṣọkọ yọ̀kọ̀tọ̀ àti ẹ̀gúsí. Mo ní láti ra èlùbọ́ fún àmàlà, |

fún oúnjẹ alẹ́.

### Iṣẹ́ Ṣíṣe 4

Dáhùn àwọn ìbéèrè wọ̀nyí.
*Answer the following questions.*

1. Níbo ni Màmáa Ṣadé àti Màmáa Fúnmi ti pàdé?
2. Kí ni ìdí tí Màmáa Ṣadé fi kí Màmáa Fúnmi pé 'a à jíbí'?
3. Ta ni ó lọ sí ìrìn àjò?
4. Kí ní Màmáa Ṣadé wá rà lọ́jà?
5. Kí ni Màmáa Fúnmi ní láti rà?

## OWÓ NÍNÁ NÍNÚ ỌJÀ

### Ìsọ̀rọ̀ngbèsì *(Dialogue)*



*Two friends, Kúnlé and Ládi meet in the market.*

– Háà Kúnlé, kí ni o wá ṣe ní ọjà?

– Màmáa mí ní kí n wá ra ẹran náírà mẹ́wàá, ìrẹsìi náírà márùnún ààbọ̀, ata rodo náírà kan, àlùbọ́sà náírà kan, èfọ́ọ tẹ̀tẹ̀ náírà méji. Wọ́n fún mi ní ogúnun náírà. Tí ìṣirò rẹ bá péjú, eélòó ni ó yẹ kí n mú padà lọ sí ilé?

– Kúnlé, ṣé o mọ̀ pé mo fẹ́ràn ìṣirò! Wà á mú …..uhhhhh…… ààdọ́ta kọ́bọ̀ padà lọ sí ilé fún màmáà rẹ. Tí o kò bá ṣe bẹ́ẹ̀, o ti wọ ìjọ̀gbọ̀nọn màmáa rẹ̀ nìyẹn.

– Ládi, èmi náà ti ṣírò iye tí ó yẹ ki n mú padà lọ sí ilé, O mọ ìṣirò gan-an ni o.

– Màmáa tèmi náà ní kí ń ra ata tàtàsé ọgọ́ta kọ́bọ̀, epo pupa náírà kan, àlùbọ́sà ọgọ́rin kọ́bọ̀, ẹ̀wà pupa náírà márùnún, gààrí náírà márùnún, nínúu náírà márùnúndínlógún. Èló lo rò wípé ó yẹ kí n mú padà lọ sí ilé?

 CC – 2012 The University of Texas at Austin

– Náíra méjí ati ogóji kọ́bọ̀.
– O gbà á. Ó dàbọ̀ o.
– Ó dàbọ̀ o.

## Iṣẹ́ Ṣíṣe 5

Dáhùn àwọn ìbéèrè wọ̀nyí.
*Respond to the following questions.*

| | True Òótọ́ ni | False Òótọ́ kọ́ |
|---|---|---|
| 1. Ládi àtí Kúnlé pàdé nílé ọtí. | ☐ | ☐ |
| 2. Màmáa Kúnlé ní kí ó lọ ra ẹran ogúnun náírà. | ☐ | ☐ |
| 3. Ogúnun náírà ni wọ́n fún Kúnlé láti ilé. | ☐ | ☐ |
| 4. Ládi kò fẹ́ràn ìṣirò rárá. | ☐ | ☐ |
| 5. Ààdọ́ta náírà ni Kúnlé máa mú padà lọ sílé. | ☐ | ☐ |
| 6. Babáa Ládi ni ó rán an lọ sí ọjà. | ☐ | ☐ |
| 7. Èfọ́ọ tẹ̀tẹ̀ wà lára nǹkan tí màmáa Kúnlé ní kí ó rà wálé. | ☐ | ☐ |
| 8. Àlùbọ́sà wà lára nǹkan tí Ládi àti Kúnlé máa rà lọ fún màmáa wọn. | ☐ | ☐ |
| 9. Kọ́bọ̀ mẹ́rìndínlógún ni màmáa Ládi fún un. | ☐ | ☐ |
| 10. Kúnlé sọ iye owó tí Ládi máa mú padà lọ fún màmáa rẹ̀. | ☐ | ☐ |

## Iṣẹ́ Ṣíṣe 6

Kọ ìsọ̀rọ̀ngbèsì kan láàárínin iwọ àti ọ̀rẹ́ẹ̀ rẹ ti ẹ jọ pàdé nínúu ọjà
*Write a dialogue between you and your friend you met in the market.*

 CC – 2012 The University of Texas at Austin

## Áṣà Ìpolówó Ọjà (Advertisement)

| | |
|---|---|
| Àgbàdo sísè: | Láńgbé jíná o<br>Ọ̀rọ̀kún orí ebè<br>Olóko ò gbowó |
| Ẹ̀wà sísè: | Àdàlú elédé o |
| Awùsá: | Awùsá gbó keke bí obì<br>Ó gbó bí orógbó |
| Iṣu sísè: | Ẹléńtú dé o.<br>Ọ̀rẹ́ ìkẹ̀tẹ́ dé o<br>Ó tú sépo múyẹ́,<br>Ó fàtàrí napo pẹ́ bẹ́ |
| Ẹkọ mímu | Ómí ẹ́ ń hó yeeyéè,<br>Yeeyéè ní ń hó o<br>Ẹ̀yin ọmọ àràbà mẹ́ta Odòokun,<br>Ẹ wa mu ún<br>Yeeyéè ní ń hó o |

## *Àwọn orin Yorùbá nípa oúnjẹ (Song about food)*

Oní mọ́ínmọ́ín gbewá gbewá
Mọ́ínmọ́ín epo
Ṣó mepo
Ṣó mepo ṣìndìn
Mọ́ínmọ́ín epo
Ṣo fedé si pẹ̀lálùbọ́sà
Mọ́ínmọ́ín epo

## *Àwọn orin Yorùbá nípa oúnjẹ (Song about food)*

Oní dòdò oní mọ́ínmọ́ín
Oní dòdò oní mọ́ínmọ́ín
Nígbà tí ò tà ó gbé gbá kalẹ̀
Ẹ wá wò jà ní Láfíàji.

 CC – 2012 The University of Texas at Austin

# Lesson 4 - Ẹ̀kọ́ Kẹrin:
# Nọ́ńbà (*Numbers*)

## Nọ́ńbà 100-3000

| | | | |
|---|---|---|---|
| 100 | ọgọ́rùnún | 300 | ọ̀ọ́dúnrún |
| 110 | àádọ́fà | 400 | irínwó |
| 120 | ọgọ́fà | 500 | ẹ̀ẹ́dẹ́gbẹ̀ta |
| 130 | àádóje | 600 | ẹgbẹ̀ta |
| 140 | ogóje | 700 | ẹ̀ẹ́dẹ́gbẹ̀rin |
| 150 | àádọ́jọ | 800 | ẹgbẹ̀rin |
| 160 | ọgọ́jọ | 900 | ẹ̀ẹ́dẹ́gbẹ̀rún |
| 170 | àádọ́sànán | 1000 | ẹgbẹ̀rún |
| 180 | ọgọ́sànán | 1200 | ẹgbẹ̀fà |
| 190 | àádọ́wàá | 1400 | egbèje |
| 200 | igba | 1600 | ẹgbẹ̀jọ |
| 203 | ẹ́ẹ́tàlénígba | 2000 | ẹgbẹ̀wá/ẹgbàá |
| 250 | àádọ́taléníigba | 2,200 | ẹgbọ̀kànlá |
| | | 2,800 | ẹgbẹ̀rìnlá |
| | | 3,000 | ẹgbẹ̀ẹ́dógún/ ẹ̀ẹ́dẹ́gbàajì |

## More on Numbers

| | | |
|---|---|---|
| Àádọ́ | = | ogún lọ́nà ilọ́po iye kan ó dín ẹ́ẹ́wàá<br>(20 x ? - 10) |
| Ẹ̀ẹ̀dẹ́ | = | igba lọ́nà ilọ́po iye kan ó dín ọgọ́rùnún<br>(200 x ? - 100) |
| Ẹ̀ẹ̀dẹ́ + ẹgbàá | = | Ẹ̀ẹ́dẹ́gbàá<br>i.e. ẹgbàá lọ́nà ilọ́po iye kan ó dín ẹgbẹ̀rún<br>(2,000 x ? -1,000) |

 CC – 2012 The University of Texas at Austin

| | | |
|---|---|---|
| ẹgbàáta | = | 6,000 (2000 x 3) |
| Therefore, ẹ̀ẹ́dẹ́gbàáta | = | 5,000 |
| ẹgbàárin | = | 8,000 |
| Therefore, ẹ̀ẹ́dẹ́gbàárin | = | 7,000 |
| ẹgbàáwàá or ọ̀kẹ́ kan | = | 20,000 |
| ọ̀kẹ́ méjì | = | 40,000 |

### Iṣẹ́ Ṣíṣe 1

Kọ ìdáhùn rẹ ní Yorùbá.
*Write your response in Yorùbá.*

**Bí àpẹẹrẹ:**

100 – 100 = òdo

1. 150 – 40 = ______
2. 200 – 60 = ______
3. 87 + 54 = ______
4. 45 x 3 = ______
5. 16 + 143 = ______
6. 78 + 125 = ______
7. 49 x 4 = ______
8. 169 – 53 = ______
9. 70 + 70 = ______
10. 200 – 132 = ______

## Iṣẹ́ Ṣíṣe 2

Kọ ìdáhùn rẹ ní Yorùbá.
*Write your response in Yorùbá .*

**Bí àpẹẹrẹ:**

Yọ ààdọ́talélọ́ọ̀ọ́dúnrún kúrò nínú ẹgbẹ̀ta. Kí ni ó kù?
Ó ku ààdọ́ta.

1. Yọ ẹgbẹ̀ta kúrò nínú ẹ́ẹ́tàdínlógúnlélẹ́gbẹ̀rin. Kí ni ó kù?
2. Yọ ẹ̀ẹ́dẹ́gbẹ̀rin kúrò nínú ẹgbẹ̀rin . Kì ni ó kù?
3. Yọ ọgọ́sànán kúrò nínú ẹgbẹ̀rún. Kí ni ó kù?
4. Yọ ọgọ́jọ kúrò nínú ọgọ́sànán. Kí ni ó kù?

## Iṣẹ́ Ṣíṣe 3

Dí àwọn àlàfo wọ̀nyí.
*Fill in the blank spaces.*

**Bí àpẹẹrẹ:**

ogún x 3 = ọgọ́ta

1. ______________________ x 4 = ọgọ́rin
2. ààd_________________________ = 180-10
3. ọgbọ̀n àti ________________ = 630
4. ẹ̀ẹ́dẹ́gbẹ̀sán dín __________ = ẹgbẹ̀jọ
5. _________________________ = 420

 CC – 2012 The University of Texas at Austin

## Iṣẹ́ Ṣíṣe 4

So àwọn tí ó bara mu ni ọ̀wọ́ A àti ọ̀wọ́ B papọ̀.
*Match the words in column A with those in column B.*

| A | B |
|---|---|
| 149 | ẹẹ́rìndínlọ́gọ̀wá |
| 196 | oókàndínláàdọ́jọ |
| 500 | igba |
| 200 | ẹ̀ẹ̀dẹ́gbẹ̀ta |
| 2000 | ẹgbẹ̀fà |
| 1200 | ẹgbàá |
| 120 | ẹgbẹ̀ta |
| 600 | ọgọ́fà |
| 60 | ààdọ́sànán |
| 170 | ọgọ́ta |

## Iṣẹ́ Ṣíṣe 5

Mú èyí tó bá tọ̀nà nínú àwọn wọ̀nyí.
*Circle the correct answer.*

1. Yọ ẹẹ́tàdínláàdóje kúrò nínú ọ̀ọ́dúnrún, ó jẹ́?
   a. ẹẹ́tàléláàdọ́sànán
   b. ẹẹ́tàlélógóje
   c. ẹẹ́rìndínlọ́gọ̀wá
   d. oókànléláàdọ́sànán
2. Yọ ẹẹ́tàdínlógún kúrò nínú ẹẹ́rìndínláààdọ́talénígba, ó jẹ́?
   a. oókàndínlọ́gbọ̀nlénígba
   b. ẹẹ́tàdínlọ́gbọ̀nlélọ́ọ̀dúnrún
   c. eéjìlélọ́gbọ̀nlénígba
   d. ẹẹ́tàlénígba
3. Yọ ogún kúrò nínú ẹẹ́tàlélọgọ́jọ, ó jẹ́?
   a. ẹẹ́tàdínláàdóje
   b. ẹẹ́tàlélógóje
   c. ẹẹ́tàléláàdóje
   d. ẹẹ́tàléláàdọ́sànán

 CC – 2012 The University of Texas at Austin

4. Aárùnúndínlọ́gọ́fà àti aárùnúndínláàádóje jẹ́?
   a. ogójìlénígba
   b. ọgbọ̀nlénígba
   c. aárùnúndínlógúnlénígba
   d. àádọ́talénígba

5. Oókàndínláàádọ́ta àti àádọ́fà jẹ́?
   a. oókànlélọ́gọ́jọ
   b. eéjìléláàdọ́jọ
   c. ẹ́ẹ́tàlélọ́gọ́jọ
   d. oókàndínlọ́gọ́jọ

6. Eéjì lọ́nà àádọ́fà jẹ́?
   a. ogúnlénígba
   b. ẹ́ẹ́tàlénígba
   c. àádọ́talénígba
   d. eéjìlénígba

7. Ẹ́ẹ́rin lọ́nà aárùnúnlélọgọ́fà jẹ́?
   a. ẹ̀ẹ́dẹ́gbẹ̀ta
   b. ẹgbẹ̀ta
   c. ọ̀ọ́dúnrún
   d. ẹ̀ẹ́dẹ́gbẹ̀rin

8. Ẹ́ẹ́tà lọna ọgọ́rùnún jẹ́?
   a. igba
   b. ọ̀ọ́dúnrún
   c. irínwó
   d. ẹ́ẹ́tàlénígba

9. Fi èéjì pín irínwó, ó jẹ́?
   a. eéjìlénirínwó
   b. ọ̀ọ́dúnrún
   c. ẹ̀ẹ́dẹ́gbẹ̀ta
   d. igba

10. Fi aárùnún pín ogúnlélẹ́ẹ̀ẹ́dẹ́gbẹ̀ta, ó jẹ́?
    a. ẹ́ẹ́rìnlélọ́gọ́rùnún
    b. ẹ́ẹ́rìnléláàdọ́fà
    c. ẹ́ẹ́rìndínlọ́gọ́rùnún
    d. ẹ́ẹ́rìnlélẹ́ẹ̀ẹ́dẹ́gbẹ̀ta



# Chapter 7 - Orí Keje | LET'S FIND SOMETHING TO EAT!

## *OBJECTIVES:*

In this chapter you will learn:

- How to express hunger and thirst
- About food in the market
- About daily meals
- How to order food in a restaurant

## Àwọn ọ̀rọ̀ (*Vocabulary*)

| Nouns | |
|---|---|
| adìẹ | *chicken* |
| alákọ̀wé | *educated person* |
| aláràṇán | *a type of fish* |
| àlejò | *visitor, guest* |
| àgbàdo | *corn* |
| agbálùmọ̀ | *wild cherry* |
| àkàrà | *food made from black eye peas/beans* |
| àlùbọ́sà | *onion* |
| àrọ̀ | *drum (fish)* |
| àṣáró | *food made from yam* |
| ata | *pepper* |
| awó | *guinea fowl* |
| bọ̀ọ̀lì | *roasted plantain* |
| bọ́tà | *butter* |
| búrẹ́dì | *bread* |
| dòdò | *fried plantain* |
| ègbo | *food made from corn* |
| èlùbọ́ | *flour made from yam* |
| èpìyà | *tilapia (fish)* |
| èso | *fruit* |
| ewédú | *a type of leafy green* |
| ẹ̀fọ́ | *leafy green* |
| ẹja | *fish* |
| ẹran | *meat/beef* |
| ẹ̀gúsí | *melon seed* |
| ẹ̀bà | *food made from cassava* |
| ẹ̀dọ̀ | *liver* |
| ẹ̀kọ | *a food made from corn* |
| ẹlẹ́dẹ̀ | *pork(pig)* |
| ẹlẹran | *meat seller* |
| ẹmu | *palm wine* |

| | |
|---|---|
| ẹ̀pà | *peanut* |
| ẹ̀wà | *beans* |
| ẹyin | *egg* |
| fàájì | *fun* |
| fáńtà | *fanta* |
| fùfú | *food made from cassava* |
| gààrí | *grains made from cassava* |
| gbẹ̀gìrì | *bean stew* |
| gúgúrú | *popcorn* |
| hámúbọ́gà | *hamburger* |
| ìbẹ́pẹ | *papaya* |
| ìgbákọ | scoop |
| ìgbín | *snail* |
| ìkọ́kọrẹ́ | *wateryam porridge* |
| ilá | *okra/okro* |
| ìnáwó | *ceremony* |
| ìpékeré | *plantain chips* |
| ìsọmọlórúkọ | *naming ceremony* |
| ìgbéyáwó | *marriage ceremony* |
| ìrẹsì/ráìsì | *rice* |
| irú | *locust bean* |
| ìsọ̀ | *stall/booth* |
| iṣu | *yam* |
| iyán | *pounded yam/ food made from yam* |
| kókà oòtù | *Quaker Oats* |
| kídìnrín | *kidney* |
| kóòkì | *Coca-Cola* |
| kọfí | *coffee* |
| màálù | *cow meat (cow)* |
| màkàróni | *macaroni* |
| máńgòrò | *mango* |
| mílîkì | *milk* |
| mínírà | *mineral/soft drinks* |
| mọ́ínmọ́ín | *food made from black eye peas/beans* |
| ọbẹ̀ | *stew* |

| | |
|---|---|
| ọ̀bọ̀kún | *a type of fish* |
| ògì | *food made from corn* |
| ògúfe | *goat meat* |
| òkèèrè | *foreign* |
| òkèlè | *morsel* |
| ọjọ́-ìbí | *birthday* |
| omi | *water* |
| oníbààrà | *customer/ buyer* |
| ọ̀pẹ̀ òyìnbó | *pineapple* |
| oríṣiríṣi | *different* |
| òróró | *vegetable oil* |
| ọsàn | *orange* |
| oúnjẹ | *food* |
| panla | *stockfish* |
| pàtàkì | *important* |
| pẹpusí | *Pepsi* |
| pọfupọ́ọ̀fù | *puff-puff (fried snack made with flour)* |
| rárá | *no* |
| tàtàsé/ tàtàṣé | *red pepper* |
| tîì | *tea* |
| sandîinì | *sardine* |
| sẹ́fúnọ̀ọ̀pù | *7 UP* |
| síríàlì | *Corn Flakes, Rice Krispies, etc* |
| ṣàkì | *tripe* |
| ṣáwá | *a type of smoked fish* |
| ṣîisì | *cheese* |
| ṣinṣîinì | *chinchin (fried snack made with flour)* |
| ṣúgà | *sugar* |
| tòlótòló | *turkey* |
| tòmáàtì | *tomato* |

## Noun Phrases

| | |
|---|---|
| àmàlà iṣu | *food made from yam* |
| àmàlàa / ọkàa láàfún | *food made from cassava* |
| ara ẹran | *meat parts* |

| | |
|---|---|
| àwọn aláṣọ | *fabric sellers* |
| dokitọ pẹ́pẹ̀ | *Dr. Pepper* |
| epo pupa | *palm oil* |
| ẹja gbígbẹ | *dried/smoked fish* |
| ẹja tùtú | *fresh fish* |
| ẹran ìgbẹ́ | *bush meat* |
| ẹsẹ ẹran | *cow leg* |
| ilé-ìtajà oúnjẹ | *restaurant* |
| jọ̀lọ́ọ̀fù ráìsì | *jollof rice* |
| màmá olóúnjẹ | *food seller* |
| ọ̀gẹ̀dẹ̀ àgbagbà | *plantain* |
| ọ̀gẹ̀dẹ̀ wẹ́wẹ́ | *banana* |
| ohun-èlò oúnjẹ | *food ingredients* |
| oúnjẹ olókèlè | *solid food (rolled into morsels)* |
| ọdún ìbílẹ̀ | *traditional festival* |
| ọdún egúngún | *the masquerading festival* |
| ọ̀bẹ̀ ilá | *okra stew* |
| ọ̀bẹ̀ ẹ̀gúsí | *melon stew* |
| ọkà gidi/ *àmàlà* | *food made from yam* |
| ọ̀nà méji | *two ways* |
| ọ̀pẹ̀ òyìnbó | *pineapple* |
| púpọ̀ nínú | *a lot of* |
| rárá kògbà | *no deal* |

## Verbs

| | |
|---|---|
| fẹ́ràn | *love/ like* |
| fẹ́ | *want/ need* |
| fún | *to give* |
| gbàgbọ́ | *to believe* |
| ná | *shop/bargain/haggle* |

## Verb Phrases

| | |
|---|---|
| dá lórí | *is about* |
| fún mi | *give me* |
| kò gbọdọ̀ | *must not* |

| | |
|---|---|
| ló pọ̀ jù | *found the most* |
| pín sí | *categorized into* |
| rìn kọjá | *walk past* |
| tún lè rí | *can also find/see* |

## Adjectives

| | |
|---|---|
| èyí | *this* |
| nìyẹn | *that* |
| ṣoṣo | *only* |
| dára | *good* |

## Adjective Phrase

| | |
|---|---|
| ju òmíràn lọ | *than another one* |

## Prepositional phrases

| | |
|---|---|
| níbẹ̀ | *there* |

## Adverb

| | |
|---|---|
| lẹ́ẹ̀kọ̀ọ̀kan | *once in a while* |

## Interrogative

| | |
|---|---|
| ṣé ó gbà…? | *can I pay…?* |

## Other Expressions

| | |
|---|---|
| bí ó ti lẹ̀ jẹ́ pe | *in spite of the fact that* |
| lọ́nà mìíràn/ nígbà mìíràn | *in another vein/ in another light/ in other ways* |
| ki a má gbàgbé pé | *don't let us forget that* |
| oúnjẹ tí kì í ṣe olókèlè | *food (not rolled into morsels* |

## Lesson 1 - Ẹ̀kọ́ Kìíní:

## Verbs ‘fẹ́, fẹ́ràn

The verb ‘fẹ́’ means ‘to want’ while ‘fẹ́ràn’ means ‘to like or to love’.

| | | |
|---|---|---|
| Mo fẹ́ oúnjẹ | → | *I want food.* |
| Mo fẹ́ owó | → | *I want, or need money.* |
| Mo fẹ́ aṣọ | → | *I want clothes.* |
| Mo fẹ́ jẹun | → | *I want to eat* |
| Mo fẹ́ sùn | → | *I want to sleep* |
| Mo fẹ́ràn oúnjẹ | → | *I like food.* |
| Mo fẹ́ràn owó | → | *I like, or love money.* |
| Mo fẹ́ràn aṣọ | → | *I like clothes.* |


One cannot say *Mo fẹ́ràn jẹun* or *Mo fẹ́ràn sùn*
One would rather say:

| | | |
|---|---|---|
| Mo fẹ́ràn láti jẹun | → | *I like to eat* . |
| Mo fẹ́ràn láti sùn | → | *I like to sleep.* |




### . Ìsọ̀rọ̀ngbèsì *(Dialogue)*

Ọ̀rẹ́ ni Túndé àti Wálé. Wálé lọ kí Túndé ní ilée wọn.
*Túndé and Wálé are friends. Wálé visits Túndé at home.*



 CC – 2011 The University of Texas at Austin

| | |
|---|---|
| **Túndé:** | Wálé, báwo ni nǹkan? |
| **Wálé:** | Dáadáa ni. |
| **Túndé:** | Àwọn ẹbí̀ rẹ ńkọ́? |
| **Wálé:** | Dáadáa ni gbogbo wọ́n wà o. Màmáà mi ní kí n máa kí ẹ. |
| **Túndé:** | Wọ́n mà ṣé o, wọ́n kú àìgbàgbé mi. |
| **Wálé:** | Àwọn òbí̀ rẹ náà ńkọ́? |
| **Túndé:** | Wọ́n ti jade láti àárọ̀, kò sì yẹ kí wọ́n pẹ́ dé mọ́. |
| **Wálé:** | Ó yẹ kí n dúró dè wọ́n, nítorí pé ó pẹ́ tí mo ti rí wọn. |
| **Túndé:** | Kí ni kí n fi ṣe ẹ́ lálejò báyìí? |
| **Wálé:** | Èmi! Àlejò? Gbogbo ohun tí o bá ní nílé pátá ni kí o gbé wá, mà á jẹ wọ́n. Àmọ́, má gbé ògì wá o. |
| **Túndé:** | Kí ló dé? |
| **Wálé:** | N kì í mu ògì. N kò fẹ́ràn ògì rárá. |
| **Túndé:** | Kò burú o, ìrẹsì àti ẹ̀wà ni mo fẹ́ fún ẹ jẹ o. |
| **Wálé:** | Ìrẹsì kẹ̀! Ṣé kò sí iyán tàbí ẹ̀bà ní? |
| **Túndé:** | Wálé! O ti fẹ́ràn òkèlè jù. Ọmọ ọkà! |
| **Wálé:** | Ṣé ìwọ ti gbàgbé ọ̀rọ̀ àwọn Yorùbá tí wọ́n sọ pé: "Iyán l'oúnjẹ, ọkà l'oògùn, Àìrí rárá là á j'ẹ̀kọ, K'ẹnu má dilẹ̀ ni ti gúgúrú." |
| **Túndé:** | Ó dára, mà á fún ẹ lẹ́bà. |
| **Wálé:** | Hẹ̀n-ẹ́n-ẹ̀n! O ṣé jàre ọ̀rẹ́. |

## Iṣẹ́ Ṣíṣe 1

Dáhùn àwọn ìbéèrè wọ̀nyí.
*Answer the following questions.*

| | True<br>Bẹ́ẹ̀ ni | False<br>Bẹ́ẹ̀ kọ́ |
|---|---|---|
| 1. Àwọn òbíi Túndé wà nílé ní ọjọ́ tí Wálé lọ kí Túndé. | ☐ | ☐ |
| 2. Wálé ni ó kọ́kọ́ kí Túndé. | ☐ | ☐ |
| 3. Kò pẹ́ tí Wálé rí àwọn òbíi Túndé. | ☐ | ☐ |
| 4. Túndé kò mọ Wálé rí tẹ́lẹ̀. | ☐ | ☐ |
| 5. Àti alẹ́ ni àwọn òbíi Túndé ti jáde. | ☐ | ☐ |
| 6. Gbogbo oúnjẹ tí Túndé ní ló gbé fún Wálé. | ☐ | ☐ |
| 7. Wálé fẹ́ràn ògì púpọ̀. | ☐ | ☐ |
| 8. Ìrẹsì àti ẹ̀wà ni Túndé fún Wálé jẹ. | ☐ | ☐ |
| 9. Wálé kò fẹ́ràn iyán. | ☐ | ☐ |
| 10. Àwọn òbíi Wálé mọ Túndé. | ☐ | ☐ |

## Iṣẹ́ Ṣíṣe 2

Lo '**mo fẹ́ràn**' láti sọ nǹkan márùnún tí o fẹ́ràn àti ìdí tí o fi fẹ́rànan wọn.
*Use '**mo fẹ́ràn**' to talk about five things you like, and state why you like them.*

**Bí àpẹẹrẹ:**

Mo fẹ́ràn owó nítorí pé mo lè fi ra ohun tí ó bá wù mi.

1. ______________________________
2. ______________________________
3. ______________________________
4. ______________________________
5. ______________________________

### Iṣẹ́ Ṣíṣe 3

Lo ‘**n kò fẹ́ràn**’ láti sọ nǹkan márùnún tí o kò fẹ́ràn àti ìdí tí o kò fi fẹ́rànan wọn.
*Use ‘**n kò fẹ́ràn**’ to talk about five things you do not like, and state why you do not like them.*

**Bí àpẹẹrẹ:**

N kò fẹ́ràn àìsàn nítorí pé kì í jẹ́ kí ń ṣe ohun tí mo bá fẹ́ ṣe.

1. ______________________________
2. ______________________________
3. ______________________________
4. ______________________________
5. ______________________________

 CC – 2011 The University of Texas at Austin

## Lesson 2 - Ẹ̀kọ́ Kejì:
## Àwọn oùnjẹ òòjọ́ (*Daily meals)*

Àwọn Yorùbá fẹ́ràn oúnjẹ wọ̀nyí:

1. Mọ́ínmọ́ín àti ògì
2. Àkàrà àti ògì
3. Iṣu àti ẹyin
4. Ẹwà àti búrẹ́dì
5. Dòdò àti ẹyin
6. Búrẹ́dì àti sandîínì
7. Búrẹ́dì àti ẹyin
8. Iṣu àti ọbẹ̀ ata
9. Búrẹ́dì àti bọ́tà
10. Síríàlì (Corn Flakes, Rice Krispies)
11. Kókà Oòtù (Quaker Oats)

1. Ẹ̀bà tàbí iyán tàbí àmàlà pẹ̀lú ọbẹ̀ ẹ̀gúsí tàbí ilá, tàbí ẹ̀fọ́, tàbí ewédú, tàbí ẹ̀fọ́ ẹlẹ́gùúsí
2. Ìrẹsì àti dòdò
3. Ìrẹsì àti mọ́ínmọ́ín
4. Ìrẹsì àti ẹ̀wà
5. Ìrẹsìi jọ̀lọ́ọ́fù àti adìẹ/ẹran/ẹja
6. Dòdò àti ẹyin
7. Dòdò àti ẹ̀wà
8. Dòdò àti mọ́ínmọ́ín

| Oúnjẹ | Ọbẹ̀ | Èèlò ọbẹ̀ | Èso | Ìpápánu |
|---|---|---|---|---|
| **olókèlè:** | | | | |
| ẹ̀bà, iyán, àmàlà, fùfú,ẹ̀bà, semolina | ọbẹ̀ ẹ̀gúsí, ilá, ẹ̀fọ́, ewédú, ẹ̀fọ́ ẹlẹ́gùúsí | tàtàsé, atarodo, tòmáàtì, àlùbọ́sà epo pupa, irú, òroro | ọ̀pẹ òyìnbó, ọ̀gẹ̀dẹ̀ wẹ́wẹ́, ìbẹ́pẹ, gúrọ́fà, ọsàn, àgbọn, máǹgòrò | ṣíninṣìn, pọfupọ́ọ̀fù, ìpékeré, kókoró, ẹ̀pà, gúrúrú, bọ̀ọ̀lì |
| **aláìlókèlè:** | | **ẹ̀fọ́:** | | |
| Ìrẹsì funfun, Ìrẹsì jọ̀lọ́ọ́fù, ẹ̀wà, dodo, mọ́ínmọ́ín, ẹyin, ògì, àkàrà, búrẹ́dì, sandîínì, iṣu, | adìẹ, ẹran, ẹja | tẹ̀tẹ̀, ṣọkọ, ewúro, gbúre | | |

 CC – 2011 The University of Texas at Austin

# Síse oúnjẹ ní ilẹ̀ẹ Yorùbá

## Ríro iyán
## (Recipe for iyán)

1. Gbé ìkòkò sórí iná
2. Da omi sínú ìkòkò
3. Jẹ́ ki omi hó
4. Da iyán sínú omi híhó
5. Ro iyán nínú omi híhó fún ìṣẹ́jú márùnún sí mẹ́wàá
6. Bí ó bá ṣe fẹ́ ẹ sí (ní líle tàbí ní rírọ̀)
7. Tí ó bá le jù, fi omi díẹ̀ sí
8. Tí ó bá rọ̀ jù, fi iyán díẹ̀ sí
9. Dé e fún bíi ìṣẹ̀jú márùnún, tún rò ó. Ó ti jinná nìyẹn!
10. Jẹ iyánàn rẹ pẹ̀lú ọbẹ̀ ilá tàbí ọbẹ̀ ẹ̀fọ́ tàbí ọbẹ̀ ẹ̀fọ́ ẹlẹ́gùúsí.

- Ẹkú ìjẹun o! (Bon appetit!)

## Èèlò ọbẹ̀ ẹlẹ́gùúsí
(*ingredients for ẹ̀gúsí stew*)

- ẹ̀gúsí
- ata
- omi
- ẹ̀fọ́
- epo pupa
- ẹran
- omi ẹran
- iyọ̀
- àlùbọ́sà

## Síse ọbẹ̀ ẹlẹ́gùúsí
## (Recipe for ẹ̀gúsí stew)

1. Lọ ẹ̀gúsí pẹ̀lú omi
2. Ge àlùbọ́sà si wẹ́wẹ́
3. Da àlùbọ́sà sinú ẹ̀gúsí
4. Gbé ìkòkò ọbẹ̀ sórí iná
5. Da epo pupa sínú ìkòkò ọbẹ̀
6. Tí epo pupa bá gbóná díẹ̀
7. Da àlùbọ́sà àti ẹ̀gúsí sínú epo pupa
8. Jẹ́ ki ó sè díẹ̀
9. Da ata lílọ̀ àti omi ẹran sínú ìkòkò ọbẹ̀
10. Ro gbogbo ẹ̀ pọ̀
11. Lẹ́yìn ìṣẹ́jú márùnún, da ẹ̀fọ́ gígé sínúu rẹ̀
12. Fi magí àti iyọ̀ sí i.
13. Lẹ́yìn ìṣẹ́jú márùnún, ó ti jiná nìyẹn!

- Ẹkú ìjẹun o! (Bon appetit!)

## Verbs 'jẹ, mu' (eat, drink)

| | | |
|---|---|---|
| Mo fẹ́ jẹ ìrẹsì. | → | *I want to eat rice.* |
| Mo fẹ́ mu omi. | → | *I want to drink water.* |
| | | |
| Mo lè jẹ ìrẹsì. | → | *I can eat rice.* |
| Mo lè mu omi | → | *I can drink water.* |

### Iṣẹ́ Ṣíṣe 1

Parí àwọn ọ̀rọ̀ wọ̀nyí.
*Complete the following sentences.*

1. Fún òùngbẹ, àwọn ènìyàn lè mu_______________________________________
2. Tí ebí bá ń pa mí, mo lè jẹ_____________________________________________
3. Tí òùngbẹ bá ń gbẹ mí, mo lè mu_______________________________________
4. Tí mo bá fẹ́ jẹ ìpápánu, mo lè jẹ________________________________________
5. Tí mo bá fẹ́ jẹ èso, mo lè jẹ_____________________________________________

 CC – 2011 The University of Texas at Austin

## Iṣẹ́ Ṣíṣe 2

Lo ọ̀rọ̀-ìṣe tó dára láti ṣàlàyé bí a ṣe le se àwọn oúnjẹ wọ̀nyí.
*Use the correct verb to describe how to prepare these foods.*

**Bí àpẹẹrẹ:**

se iṣu

1. _______________ iyán
2. _______________ ẹyin
3. _________ ìrẹsì jọ̀lọ́ọ́fù
4. _____________ àmàlà
5. _______________dòdò
6. _______________ ẹ̀wà
7. _____________ àṣáró
8. _______________ ẹ̀bà
9. _____________ àkàrà
10. ________________ògì

## Iṣẹ́ Ṣíṣe 3

Lo ọ̀rọ̀-ìṣe tó dára láti ṣàlàyé àwọn oúnjẹ àti nǹkan mímu wọ̀nyí.
*Use the correct verb to describe eating or drinking of the following.*

**Bí àpẹẹrẹ:**

mu omi

1. _______________ ẹ̀bà
2. _______________ ẹmu
3. ______________ kóòkì
4. _____________ àmàlà
5. ________________ ògì

 CC – 2011 The University of Texas at Austin

## Iṣẹ́ Ṣíṣe 4

Dáhùn àwọn ìbéèrè wọ̀nyí ní ẹ̀kúnrẹ́rẹ́.
*Answer the following questions in complete sentences.*

1. Kí ni àwọn oúnjẹ àárọ̀ mẹ́rin tí àwọn Yorùbá lè jẹ?
2. Kí ni àwọn oúnjẹ ọ̀sán márùnún tí àwọn Yorùbá lè jẹ?
3. Dárúkọ àwọn nǹkan mẹ́rin tí ìwọ máa ń jẹ ní àárọ̀?
4. Dárúkọ àwọn oúnjẹ mẹ́ta tí àwọn Yorùbá lè jẹ ní alẹ́?
5. Kí ni àwọn eso mẹ́ta tí ìwọ fẹ́ràn láti jẹ?
6. Kí ni àwọn ọmọdé fẹ́ràn láti jẹ ní ilúù rẹ?
7. Kí ni àwọn ọmọdé fẹ́ràn láti mu ní ilúù rẹ?
8. Kí ni màmáà rẹ fẹ́ràn láti jẹ ní àárọ̀?
9. Àwọn oúnjẹ wo ni bàbáà rẹ fẹ́ràn láti jẹ?
10. Àwọn èso wo ni màmáà rẹ fẹ́ràn láti jẹ?
11. Kí ni àwọn nǹkan tí ìwọ fẹ́ràn láti mu?
12. Àwọn èso wo ni ìwọ fẹ́ràn láti jẹ?
13. Kí ni àwọn nǹkan tí ìwọ lè jẹ ní ọ̀sán?
14. Kí ni àwọn nǹkan tí bàbáà rẹ fẹ́ràn láti mu?
15. Kí ni àwọn nǹkan tí àwọn ẹbí rẹ lè jẹ ní alẹ́?

 CC – 2011 The University of Texas at Austin

### Iṣẹ́ Ṣíṣe 5

Fi èyí tó bá yẹ dí àwọn àlàfo wọ̀nyí
*Fill in the spaces below with appropriate pronouns.*

Nígbà tí mo délé láti ilé–ìwéè mi, màmáà mi bi mí pé kí ni mo fẹ́____________. Mo dá wọn lóhùn pé iyán ni. Wọ́n sọ wipe àwọn kò lè ____________iyán ní àsìkò náà torí pé ó ti rẹ àwọn, ṣùgbọ́n tí ó bá jẹ́ àmàlà ni mo fẹ́ ni, àwọn ṣìlè____________ò. Màmáà mi____________àmàlà fún mi, mo sì ____________ẹ́ pẹ̀lú ọbẹ̀ ewédú àti ẹran. Mo fẹ́ràn màmáà mi gan-an ni.

### Iṣẹ́ Ṣíṣe 6

Ṣe àlàyé bí wọ́n ṣe máa ń ṣe oúnjẹ kan nílúù rẹ.

 CC – 2011 The University of Texas at Austin

## Lesson 3 - Ẹ̀kọ́ Kẹta:
## In the market

### Ìsọ̀rọ̀ngbèsì *(Dialogue)*

**Ìsọ̀rọ̀ngbèsì láààrin Bùnmi àti Tósìn. (*Dialogue between Bùnmi and Tósìn.*)**

**Bùnmi**: Kí ni orúkọ ọjà tí wọ́n ń ná ní àdúgbò tí a rìn kọjá yẹn?

**Tósìn**: Ọjàa Sáńgo ni.

**Bùnmi**: Ṣé ọjà kan ṣoṣo tí ó wà ní ìlú Ìbàdàn nìyẹn ni?

**Tósìn**: Rárá o!

**Bùnmi**: Kí ni orúkọ àwọn ọjà tí ó kù àti àwọn ohun tí a lè rí rà ní ibẹ̀?

**Tósìn**: Oríṣiríṣi ọjà ló wà ní ìlú Ìbàdàn yìí. Nínúu wọn ní a ti rí Ọjàa Sáńgo, Ọjàa Màpó, Ọjà Alẹ́ṣinlọ́yẹ́, Ọjàa Dùgbẹ̀, àti Ọjà Orítamẹ́rin. Bí àpẹẹrẹ, a lè rí ohun èlò ẹnú ń jẹ rà ní ọjà Alẹ́ṣìnlọ́yẹ́ bí ó ti lẹ̀ jẹ́ pé ìsọ̀ àwọn álaṣọ ló pọ̀ jù níbẹ̀. Àwọn èlò oúnjẹ bíi ata, tòmáàtì, epo pupa, irú, òróó, àlùbọ́sà, ilá, ẹ̀gúsí àti oúnjẹ bíi ìrẹsì, ẹ̀wà, àgbàdo, ẹja, ẹran, gàrí, èlùbọ́, àti ẹ̀fọ́. A tún lè rí àwọn èso bíi ọsàn, máńgòrò, ìbẹ́pẹ àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ ní àwọn ọjà wọ̀nyí. Nínú àwọn ọjà tí mo dárúkọ wọ̀nyí, a lè sọ wípé Ọjàa Sáńgo, Màpó, àti Alẹ́ṣinlọ́yẹ́ ni àwọn ọjà tí wọ́n tóbi jù ní ìlú Ìbàdàn.

**Bùnmi**: Ẹ̀yí mà dára o. Wọ́n yàtọ̀ púpọ̀ sí àwọn ọjà tí a máa ń ná ní Ilé-Ifẹ̀.



## Iṣẹ́ Ṣíṣe 1

Dáhùn àwọn ìbéèrè wọ̀nyí ní ẹ̀kúnrẹ́rẹ́.

*Answer the following questions in complete sentences.*

1. Kí ni orúkọ ọjà tí Bùnmi àti Tósìn rìn kọjá?

   ______________________________

2. Yàtọ̀ sí èlò oúnjẹ àti oúnjẹ, kí ni nǹkan tí a tún lè ra ni ọjà Alẹ́ṣinlọ́yẹ́?

   ______________________________

3. Kí ni orúkọ ìlú tí Bùnmi ti wá?

   ______________________________

4. Orúkọ ọjà mèlòó ni Tósìn dárúkọ?

   ______________________________

5. Dárúkọ àwọn ọjà tí Tósìn sọ wípé wọ́n tóbi jù ní ìlú Ìbàdàn?

   ______________________________

6. Kí ni àwọn élò oúnjẹ tí a lè rà ní ọjà Alẹ́ṣinlọ́yẹ́?

   ______________________________

7. Dárúkọ àwọn ọjà tí ó wà ní ìlúù rẹ.

   ______________________________

8. Kí ni àwọn élò oúnjẹ tí a lè rí rà ní àwọn ọjà tí ó wà ní ìlúù rẹ?

   ______________________________

9. Kí ni ìdíí rẹ̀ tí Bùnmi fi sọ wipé “Èyí mà dára o”?

   ______________________________

10. Níbo ni ìlú Ìbàdàn wà?

    ______________________________


CC – 2011 The University of Texas at Austin

## Iṣẹ́ Ṣíṣe 2

Mú èyí tó bá tọ̀nà nínú àwọn wọ̀nyí.

*Circle the correct answer.*

Dáhùn àwọn ìbéèrè wọ̀nyí ní ẹ̀kúnrẹ́rẹ́. Dáhùn àwọn ìbéèrè wọ̀nyí ní ẹ̀kúnrẹ́rẹ́.

1. Kí ni orúkọ ọjà kan tí ó wà ní ìlú Ìbàdàn tí Tósìn dárúkọ?
   a. Ọjàa Dùgbẹ̀
   b. Ọjà Ọba
   c. Ọjà Ilé-Ifẹ̀
   d. Ọjà Orítamẹ́fà

2. Kí ni wọn ń tà ní Ọjà Alẹ́ṣinlọ́yẹ́?
   a. asọ
   b. bàtà
   c. aago
   d. àwòrán

3. Ọjà wo ni ó tóbi jù láàárin àwọn ọjà tí wọ́n wà ní ìlú Ìbàdàn?
   a. Ọjàa Màpó
   b. Ọjàa Dùgbẹ̀
   c. Ọjà Orítamẹ́rin
   d. Ọjà Ọba

4. Kí ni orúkọ ìlú ti Tósìn ti wá?
   a. Ilé-Ifẹ̀
   b. Ìbàdàn
   c. Èkó
   d. Abẹ́òkúta

5. Orúkọ ọjà mélòó ni Tósìn dárúkọ pe wọ́n tóbi jù ní ìlú Ìbàdàn?
   a. Mẹ́ta
   b. Méjì
   c. Márùnún
   d. Mẹ́fà

## Oúnjẹ ní ilẹ̀ẹ Yorùbá (*Food in Yorùbá land*)

Oúnjẹ olókèlè àti oúnjẹ tí kìí ṣe olókèlè ni ọ̀nà méji pàtàkì tí àwọn oúnjẹ Yorùbá pín sí. Àwọn oúnjẹ olókèlè ni ẹ̀bà, iyán, àmàlà iṣu, àmàlàa láfún àti fùfú. Àwọn oúnjẹ tí kì í ṣe olókèlè ni ìrẹsì, ègbo, ẹ̀wà, àṣáró àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ.  Púpọ̀ nínú àwọn oúnjẹ olókèlè ni wọ́n máa ń fi ẹ̀gẹ́ ṣe. Ẹ̀gẹ́ ni wọ́n fi ń ṣe gààrí, àmàlàa láfún àti fùfú. Nínúu gààrí lati rí ẹ̀bà. Nínú iṣu lati rí àmàlà iṣu àti iyán.

Oríṣiríṣi ọbẹ̀ ni àwọn Yorùbá máa ń jẹ. Díẹ nínú àwọn ọbẹ̀ yìí ni ọbẹ̀ ẹ̀fọ́, ilá, amúnútutù, ẹ̀gúsí, ewédú àti gbẹ̀gìrì. Ọbẹ̀ ilá dára fún oúnjẹ òkèlè bíi ẹ̀bà. Ọbẹ̀ ẹ̀gúsí ni àwọn ènìyàn sáábà máa ń fi jẹ iyán. Ọbẹ̀ ewédú àti gbẹ̀gìrì ni àwọn ènìyàn gbogbo sọ wípé ó dára jù fún àmàlàa láfún àti àmàlà iṣu. Oríṣiríṣi ọbẹ̀ ẹ̀fọ́ ni ó wà: ọbẹ̀ ẹ̀fọ́ọ ṣọkọ, tẹ̀tẹ̀, gbúre, ewúro àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ.

Oríṣiríṣi ẹran ni wọ́n fi ń se ọbẹ̀. Nínu àwọn ẹran wọ̀nyí ni ẹran ògúfe, màálù, ẹlẹ́dẹ̀ àti ẹran ìgbẹ́. Oríṣiríṣi ara ẹran ni wọ́n sì ń jẹ. Nínúu wọn ni ṣàkì, ẹ̀dọ̀ àti kídìnrín. Àwọn Yorùbá sì máa ń fi ẹja se ọbẹ̀ nígbà mìíràn. Nínu àwọn ẹja wọ̀nyí ni ẹja àrọ̀, èpìà, ọ̀bọ̀kún, alárànán, panla, ṣáwá àti ẹja gbígbẹ. Wọ́n sì tún máa ń fi adìẹ, tòlótòló, awó àti ìgbín se ọbẹ̀ pẹ̀lú.

Yorùbá gbàgbọ́ wípé àwọn ẹ̀yáa Yorùbá kọ̀ọ̀kan fẹ́ràn oúnjẹ kan ju òmíràn lọ.  Bí àpẹẹrẹ, àwọn Èkìtì fẹ́ràn iyán. Àwọn Ìbàdàn ni ó ni àmàlà láfún. Àwọn Ìjẹ̀bú fẹ́ranan gààrí àti ẹ̀bà. Ọwọ́ ni àwọn Yorùbá fi máa ń sáábà jẹ òkèlè nítorí pé wọ́n ní ìgbàgbọ́ pé àtẹlẹwọ́ ẹni kì í tan ní jẹ. Ṣùgbọ́n àwọn mìíràn máa ń fi fọ́ọ̀kì jẹ̀un.

Àwọn Yorùbá sì máa ń jẹ èso bíi ọsàn (òrombó), ìbẹ́pẹ, ọ̀pẹ̀ òyìnbó, àgbálùmọ̀ àti ọ̀gẹ̀dẹ̀ wẹ́wẹ́. Ìpápánu bíi bọ̀ọ̀li àti ẹ̀pà wà lára oúnjẹ tí àwọn ènìyàn máa ń jẹ.  Bọ̀ọ̀lì ni ọ̀gẹ̀dẹ tí wọ́n yan. Àwọn ènìyàn tun máa ń jẹ ìpékeré, gúgúrú, ẹ̀pà àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ.

Ní gbogbo ìgbà ni àwọn Yorùbá máà ń mu omi pẹ̀lú oúnjẹ wọn. Ṣùgbọ́n lẹ́ẹ̀kọ̀ọ̀kan, wọ́n máa ń mu mínírà bíi kóòkì, fáńtà àti pẹpusí. Nígbà mìíràn, wọ́n tún máa ń mu ẹmu fún fàájì tàbí nígbà ìnáwó bíi ìṣílé, ìsọmọlórúkọ, ìgbéyàwó, ọjọ́ ìbí àti ọdún ìbílẹ̀ bíi ọdún egúngún. Ki a má gbàgbé pé àwọn Yorùbá náà máa ń mu tîì tábí kọfí o!


CC – 2011 The University of Texas at Austin

## Iṣẹ́ Ṣíṣe 3

Dáhùn àwọn ìbéèrè wọ̀nyí ní ẹ̀kúnrẹ́rẹ́.
*Answer the following questions in complete sentences.*

1. Ọ̀ná mélòó ni oúnjẹ tí àwọn Yorùbá máa ń jẹ pín sí?
2. Kí ni àwọn oúnjẹ olókèlè?
3. Kí ni àwọn oúnjẹ tí kì í ṣe olókèlè?
4. Irú oúnjẹ wo ni àwọn Ìbàdàn fẹ́ràn?
5. Oúnjẹ wo ni àwọn Èkìtì fẹ́ràn?
6. Dárúkọ ìpápánu méjì tí àwọn Yorùbá máa ń jẹ.
7. Oríṣi ọbẹ̀ mélòó ni a dárúkọ nínú àròkọ yìí?
8. Kí ni a máa ń fi ṣe púpọ̀ nínú àwọn oúnjẹ olókèlè?
9. Ọbẹ̀ wo ni ó dára fún oúnjẹ òlókèlè?
10. Kí ni ìdíi rẹ̀ tí àwọn Yorùbá fi ń fọwọ́ jẹun?
11. Kí ni ìpápánu tí àwọn ènìyàn máa ń jẹ ní ìlúù rẹ?
12. Kí ni àwọn oúnjẹ tí kì í ṣe olókèlè tí ìwọ máà ń jẹ?
13. Kí ni àwọn oúnjẹ tí ìwọ máà ń fi ọwọ́ jẹ?
14. Kí ni àwọn oúnjẹ ìlú òkèèrè tí àwọn Yorùbá máa ń jẹ?
15. Irú oúnjẹ wo ni ó yẹ kí àwọn ènìyàn máa jẹ? Kí n ìdíí rẹ̀?


CC – 2011 The University of Texas at Austin

## Iṣẹ́ Ṣíṣe 4

To àwọn oùnjẹ tí o rí kà nínú àyọkà yìí sí abẹ́ àwọn ọ̀rọ̀ wọ̀nyí.
*List the various types of food or drink you read in the passage above into the groups below.*

1. Oúnjẹ olókèlè: ______________________________
2. Oúnjẹ tí kì í ṣe olókèlè: ______________________________
3. Ìpápánu: ______________________________
4. Nǹkan mímu: ______________________________
5. Ọbẹ̀: ______________________________

## Iṣẹ́ Ṣíṣe 5

To àwọn oùnjẹ tí o mọ̀ ní ìlúù rẹ sí abẹ́ àwọn ọ̀rọ̀ wọ̀nyí.
*List the various types of food or drink in your country under the categories below.*

1. Oríṣiríṣi ẹja: ______________________________
2. Oúnjẹ tí kì í ṣe olókèlè: ______________________________
3. Ìpápánu: ______________________________
4. Nǹkan mímu: ______________________________
5. Ọbẹ̀: ______________________________
6. Oúnjẹ àárọ̀: ______________________________
7. Oúnjẹ ọ̀sán: ______________________________
8. Oúnjẹ alẹ́: ______________________________
9. Oríṣiríṣi ẹ̀fọ́: ______________________________
10. Oríṣiríṣi ẹ̀wà: ______________________________

 CC – 2011 The University of Texas at Austin

## Iṣẹ́ Ṣíṣe 6

Kọ ìtumọ̀ àwọn ọ̀rọ̀ wọ̀nyìí sílẹ̀ ní èdèe Yorùbá

*Write down the meaning of the following expressions in Yorùbá*


1. ohun-èlò ẹnú-ń-jẹ
2. wọ́n yàtọ̀
3. oúnjẹ olókèlè
4. àtẹlẹwọ́ ẹni kì í tan ní jẹ
5. ìsọmọlórúkọ
6. ìgbéyáwó

 CC – 2011 The University of Texas at Austin

## Lesson 4 - Ẹ̀kọ́ Kẹrin:
## Rírà oúnjẹ nínúu búkà tàbí ilé ìtajà oúnjẹ.
## (*Ordering food in a restaurant*)

Àwọn ilé ìtajà oúnjẹ alábọ́dé ti wà káàkiri ilẹ̀ẹ Yorùbá. Àwọn oúnjẹ òkèèrè bíi meat pie, salad, chicken pie, egg buns àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ, pẹ̀lú àwọn oúnjẹ ìbílẹ̀ bìí iyán, ẹ̀bà àti àmàlà ni wọ́n ń tà ní ilé àwọn oúnjẹ yìí. Púpọ̀ nínúu wọn wà ní ìlú ńlá bíi Èkó àti Ìbàdàn. Àwọn akẹ́kọ̀ọ́ lọ́ sáábà máa ń jẹun ní àwọn ilé oúnjẹ yìí. Díẹ̀ nínú àwọn ilé oúnjẹ yìí ni Tantalizer, Mr. Biggs àti Right Choice.

### . Ìsọ̀rọ̀ngbèsì (*Dialogue*)



| | |
|---|---|
| **Oníbàárà**: | Màmá, irú oúnjẹ wo ni ẹ ní? |
| **Màmá Olóúnjẹ:** | Ẹ̀bà, iyán, ọkà gidi àti fùfú. |
| **Oníbàárà**: | Irú ọ̀bẹ̀ wo ló wà? |
| **Màmá Olóúnjẹ:** | Ọbẹ ilá, ẹ̀gúsí, ewédú àti gbẹ̀gìrì. |
| **Oníbàárà**: | Irú ẹran wo ló wà? |
| **Màmá Olóúnjẹ:** | Ẹran ògúnfe, màlúù àti ọ̀yà. |
| **Oníbàárà**: | Ẹja ń kọ́? Irú ẹja wo ló wà? |
| **Màmá Olóúnjẹ:** | Ẹja ṣáwá, ẹja èpìà, ẹja aborí àti ẹja àrọ̀. |
| **Oníbàárà**: | Eélòó ni ìgbákọ àmàlà kan? |
| **Màmá Olóúnjẹ:** | Ogúnun náírà. |

| | |
|---|---|
| **Oníbàárà**: | Ṣé ó gba náírà márùnúndínlógún? |
| **Màmá Olóúnjẹ**: | Rárá, kò gbà. Ogúnun náírà ni ìgbákọ. |
| **Oníbàárà**: | Ẹ fún mi ní ìgbakọ mẹ́rin. |
| **Màmá Olóúnjẹ**: | Irú ọbẹ̀ wo lẹ fẹ́? Ọbẹ̀ ilá, ewédú, gbẹ̀gìrì, ẹ̀gúsí àti ẹ̀fọ́ rírò. |
| **Oníbàárà**: | Ẹ fún mi ní àbùlà. |
| **Màmá Olóúnjẹ**: | Ẹrán ńkọ́? |
| **Oníbàárà**: | Eélòó ni ẹran kọ̀ọ̀kan? |
| **Màmá Olóúnjẹ**: | Náírà márùnún ni ẹran kọ̀ọ̀kan. |
| **Oníbàárà**: | Ẹ fún mi ní ẹran méjì? |
| **Màmá Olóúnjẹ**: | Ṣé omi lẹ fẹ́ tàbí mínírà? |
| **Oníbàárà**: | Irúu mínírà wo lẹ ní? |
| **Màmá Olóúnjẹ**: | A ní fáńtà, kóòkì, sípíráìtì, sẹ́fúnọ̀ọ̀pù, pẹpusí àti dọ́kítọ̀ pẹpẹ̀. |
| **Oníbàárà**: | Eélòó ni kóòkìi yín? |
| **Màmá Olóúnjẹ**: | Ọgbọ̀nọn náírà ni. |
| **Oníbàárà**: | Ẹ fún mi ní kóòkì kan. Eélòó ni owó mi jẹ́? |
| **Màmá Olóúnjẹ**: | Owóo yín jẹ́ ọgọ́fàa náírà. |
| **Oníbàárà**: | Ẹ gba owó. |
| **Màmá Olóúnjẹ**: | Ẹ ṣé o. (Oníbàárà gba oúnjẹ, ó sì wọ inúu búkà lọ láti jẹ oúnjẹ rẹ̀.) |

## Iṣẹ́ Ṣíṣe 1

Dáhùn àwọn ìbéèrè wọ̀nyí ní ẹ̀kúnrẹ́rẹ́.
*Answer the following questions in complete sentences.*

1. Irú oúnjẹ wo ni màmá olóúnjẹ ní?
   ______________________________
2. Irú nǹkan mímu wo ni màmá olóúnjẹ ní?
   ______________________________
3. Oúnjẹ wo ni oníbàárà rà?
   ______________________________
4. Eélòó ni oníbàárà san?
   ______________________________
5. Kí ni oníbàárà mu?
   ______________________________

 CC – 2011 The University of Texas at Austin

## Iṣẹ́ Ṣíṣe 2

Lo 'eélòó' láti fi bèèrè iye tí wọ́n ń ta àwọn oúnjẹ wọ̀nyí.
*Use the interrogative 'eélòó' to ask for the price of the following items*

**Bí àpẹẹrẹ:**

ẹ̀wà / ₦ 10
Eélòó ni ẹ̀ ń ta ẹ̀wà?
Náírà mẹ́wàá ni.

1. Ẹ̀bà àti ọbẹ̀ ilá / ₦150
2. Ẹ̀kọ àti mọ́ínmọ́ín / ₦120
3. Kóòkì ìgò méjì / ₦200
4. ìrẹsì jọ̀lọ́ọ̀fù / ₦70
5. ìrẹsì, dòdò àti ẹ̀wà / ₦500
6. ìrẹsì, dòdò àti ẹja / ₦600
7. iyán, ọbẹ̀ ẹ̀fọ́ àti ẹran / ₦750
8. àmàlà, ọbẹ̀ ewédú àti adìẹ / ₦ 690
9. búrẹ́dì, ẹyin àti tíì / ₦170
10. búrẹ́dì, ẹyin, tíì àti ọ̀gẹ̀dẹ̀ / ₦ 190

 CC – 2011 The University of Texas at Austin

## Iṣẹ́ Ṣíṣe 3

Wá àwọn ọ̀rọ̀ wọ̀nyí.

*Look for these words in the puzzle below. Pay attention to the tones!*

**adìẹ, àkàrà, àlùbọ́sà, àgbàdo, dòdò, búrẹ́dì, fùfú, ìnáwó, ẹran, míníràn**

| | | | | | | | | | | | | | | |
|---|---|---|---|---|---|---|---|---|---|---|---|---|---|---|
| a | f | u | f | ú | l | m | í | n | í | r | à | d | n | a |
| b | d | l | u | ẹ | g | i | i | ẹ | f | u | n | f | u | d |
| u | o | ì | f | ẹ | b | n | f | n | e | w | à | s | k | i |
| r | a | n | ẹ | r | a | i | u | b | i | r | í | k | í | e |
| e | g | á | a | a | l | r | f | u | n | r | e | s | i | f |
| d | b | w | s | n | e | a | u | l | o | l | a | ì | n | u |
| i | a | ó | ò | ì | n | a | w | d | a | à | d | à | d | f |
| a | l | ì | b | ọ́ | s | a | à | n | ò | ẹ́ | h | i | l | u |
| ẹ | r | a | n | i | l | b | a | b | r | d | i | l | o | b |
| f | ú | f | u | n | g | e | f | ù | f | ú | ò | í | a | s |
| d | o | d | o | à | l | ù | b | ọ́ | s | à | d | b | g | a |
| ẹ | b | u | r | e | d | i | i | g | b | a | l | e | u | b |
| a | k | à | r | a | m | i | n | i | r | a | n | u | e | r |
| o | k | u | n | r | i | n | à | n | m | o | e | s | n | à |
| à | b | u | r | ẹ́ | d | ì | a | g | b | a | d | ò | d | o |

 CC – 2011 The University of Texas at Austin



# Chapter 8 - Orí Kẹ̀jọ | ARE YOU FEELING GOOD TODAY?

## *OBJECTIVES:*

In this chapter you will learn:

- How to use possessive forms of emphatic pronouns
- About parts of the body
- How to express what to do with different parts of the body
- About the future tense
- About health and sickness
- About different types of sport

## Àwọn ọ̀rọ̀ (*Vocabulary*)

| Nouns | |
|---|---|
| aboyún | *pregnant lady* |
| àgbo | *concoction* |
| aládàáni | *private* |
| apá | *arm* |
| apòògùn | *pharmacist* |
| àrùn | *disease/illness* |
| babaláwo | *the healers* |
| babańlá | *ancestor* |
| èjìká | *shoulder* |
| eré sísá | *athletics* |
| ewé | *leaf* |
| ẹ̀ka | *branch* |
| ẹsẹ̀ | *leg/foot* |
| ẹ̀ṣẹ́ jíjà | *boxing* |
| gbajúmọ̀ | *common* |
| ìdàgbàsókè | *progress* |
| iṣẹ́ | *work* |
| iṣẹ́ abẹ | *surgery* |
| ìlú | *city/town* |
| irin ìsẹ́ | *tool* |
| itan | *thigh* |
| Ìyá Àbíyè | *midwife* |
| nọ́ọ̀sì | *nurse* |
| òlíńpîkì | *Olympics* |
| oníṣègùn | *doctor* |
| oníṣẹ́ abẹ | *surgeon* |
| ọ̀làjú | *civilization* |
| yọyínyọyín (dókítà eyín) | *dentist* |

## Noun Phrases

| | |
|---|---|
| agbára omi àti ewé | *the power of water and herbs* |
| alábòójútó erée bọ́ọ̀lù àfẹsẹ̀gbá/rẹfirí | *soccer referee* |
| àlọ́ pípa | *telling of folktales* |
| bọ́ọ̀lù àjùsáwọ̀n | *basketball* |
| bọ́ọ̀lù àfọwọ́gbá | *handball* |
| bọ́ọ̀lù àfẹsẹ̀gbá | *soccer* |
| dókítà àrùn ọpọlọ | *psychiatrist* |
| dókítà eyín | *dentist* |
| dókítà ojú | *optometrist* |
| dókítà olùtọ́jú obìnrin | *gynecologist* |
| dókítà ọmọdé | *pediatrician* |
| egbò igi/ egbòogi | *medicine* |
| eléwé ọmọ | *herb seller* |
| eré ìdárayá | *sport/ game* |
| Ìjàkadì tàbí ẹkẹ | *wrestling* |
| ilé ìta òògùn | *pharmacy* |
| ilé ìbímọ | *delivery room* |
| ilé ìwòsàn ìjọba | *Government/General hospital* |
| ilé ẹ̀kọ́ gíga | *institution of higher education* |
| iṣẹ àjogúnba | *inherited job* |
| iṣẹ́ àrùn wíwò | *the job of curing diseases* |
| Iṣẹ́ ìṣègùn | *medical practice* |
| ìtọ́jú aboyún | *pre-natal care* |
| ìtọ́jú aláìsàn | *care of the sick* |
| ìtọ́jú ọmọdé | *children's care* |
| ìwé àṣẹ ìtọ́jú aláìsàn | *authorization to take care of the sick* |
| ìwòsàn òyìnbó | *western medicine* |
| ohun búburú | *evil* |
| òkè ọrùn | *above the neck* |
| olùrànlọ́wọ́ rẹfirí | *assistant referee/line man* |
| oníṣègùn ìbílẹ̀ | *traditional doctor* |
| òyìnbó amúnisìn | *colonial master* |
| ọmọ ìkókó | *an infant* |
| ọ̀pọ̀lọpọ̀ ọ̀nà | *several ways* |
| pápá ìṣeré | *playground* |

 CC – 2011 The University of Texas at Austin

## Verbs

| | |
|---|---|
| dìde | *to stand up* |
| fò | *to jump* |
| fún | *to give* |
| gbóòórùn | *to smell* |
| gbọ́rọ̀ | *to hear* |
| jà | *to fight* |
| jẹun | *to eat* |
| jókòó | *to sit down* |
| juwọ́ | *to wave hand* |
| kàpọ̀ | *to put together* |
| kàwèé | *to read* |
| kọ̀wèé | *to write* |
| lò | *to use* |
| pàtẹ́wọ́ | *to clap* |
| rà | *to buy* |
| rẹ́rìnín | *to laugh* |
| rìn | *to walk* |
| ríran | *to see* |
| ronú | *to think* |
| sáré | *to run* |
| sín | *to sneeze* |
| sunkún | *to cry* |
| wẹ̀ | *to take a bath* |

## Verb Phrases

| | |
|---|---|
| bá … jà (serial verb) | *to be afflicted with; fight with* |
| fi ṣe (serial verb) | *make do* |
| fojú sí | *to observe* |
| fọ ẹnu | *to brush teeth* |
| fun fèrè | *to play trumpet; to blow balloon* |
| gba bọ́ọ̀lù | *to play soccer* |
| gba ìwé àṣẹ | *to get permission* |
| gba ìwúre | *go to parents for prayers* |
| gbá tẹníìsì | *to play tennis* |

 CC – 2011 The University of Texas at Austin

| | |
|---|---|
| jẹ́ ohun tí | *is something that* |
| jẹ oúnjẹ àárọ̀ | *to eat breakfast* |
| jogún àìsàn wíwò | *to inherit the healing of diseases* |
| jogún iṣẹ́ | *inherit the profession* |
| jọ̀ọ́ kúrò ojère | *please, leave me alone* |
| kò ní láti gbà | *do not have to obtain* |
| kun ojú | *to put on make-up* |
| láti fi ṣe | *to make* |
| láti fi wo ààrùn | *to cure disease/illness* |
| láti já ewé | *to pluck leaves* |
| láti gbẹ̀bí | *to deliver (baby)* |
| láti mọ irú àrùn | *to know what type of disease* |
| lo agbára | *to use power* |
| lọ sí ilé-ìwé | *to go to school* |
| lọ rí (serial verb) | *to go see* |
| máa ń bọ Òrìṣà Ọlọ́mọ | *to worship the children's deity* |
| máa ń dá ifá | *to consult the oracle* |
| máa ń gbo pọ̀ | *to combine/to mix* |
| mọ̀ wípé | *to know that* |
| mú… wá (serial verb) | *to bring* |
| ní ìgbàgbọ́ wípé | *to have the belief that* |
| nu ara | *to dry body* |
| pa ara | *to put on body lotion* |
| ran … lọ́wọ́ | *to help* |
| ṣe ìtọ́jú ọmọ ìkókó | *to take care of the infant* |
| sọ wípé | *to say that* |
| tẹ dùrù | *to play piano* |
| tọ́ nǹkan wò | *to taste something* |
| wà lára | *to be among* |
| wo tẹlifíṣàn | *to watch TV* |
| wọ aṣọ | *to put on clothes* |
| wọ bàtà | *to wear shoes* |
| ya irun | *to comb hair* |

 CC – 2011 The University of Texas at Austin

## Adjectives

| | |
|---|---|
| ọ̀pọ̀lọpọ̀ | *several* |
| wọ̀nyí | *these* |
| wọ́pọ̀ | *common* |
| yàtọ̀ | *different* |

## Adverbs

| | |
|---|---|
| sáábà | *usually* |
| tún | *also* |

## Adverbial phrase

| | |
|---|---|
| tí mo bá jí | *when I wake up* |

## Prepositional phrases

| | |
|---|---|
| bíi Ọ̀ṣun àti Ọya | *such as Ọ̀ṣun and Ọya* |
| inú igbó | *inside the bush/forest* |
| kí ayé tó di ayé ọ̀làjú | *before the world became civilized* |
| kí wọ́n tó lè ṣe | *before they can do/make* |
| kí wọ́n tó gba | *before they can be given/awarded* |
| láti fi ṣe ìtọ́jú | *for taking care of* |
| láti kékeré | *from childhood* |
| láti òkè òkun | *from abroad/ from overseas* |
| láti … | *from …* |
| láti ọwọ́ àwọn babańlá | *from the ancestors* |
| lọ́wọ́ Ìjọba | *from government* |
| ní àárín | *in between/in the middle of* |
| ní ìgbàgbọ́ wípé | *believe that* |
| ní òwúrọ̀/àárọ̀ | *in the morning* |
| nípa | *about* |
| nítorí èyí ni | *it's because of this* |
| nítòrí ìdí èyí | *for this reason; because of this* |
| yàtọ̀ sí eléyìí | *besides this* |

 CC – 2011 The University of Texas at Austin

| Other Expressions | |
|---|---|
| àwọn èyí tí ó wọ́pọ̀ | *the most common* |
| bojúbojú àti ẹkùn mẹ́ran | *types of hide and seek games* |
| Ìlera ni oògùn ọrọ̀ | *health is wealth* |
| ìtumọ̀ èyí ni pé | *this implies/this means that* |
| o dé nìyẹn | *You have come again* |
| ó ṣe pàtàkì láti | *it is important to* |
| púpọ̀ nínú | *a lot of / many* |
| ṣe tán | *on completion/completed* |
| tí ó bá ń bá ènìyàn jà | *that people are afflicted with* |

 CC – 2011 The University of Texas at Austin

# Lesson 1 - Ẹ̀kọ́ Kìíní:
## Possessive forms of emphatic pronouns
## Possessive Pronouns

| Singular | | | Plural | | |
|---|---|---|---|---|---|
| 1st pers. | tèmi | *mine (m/f)* | 1st pers. | tàwa | *ours (m/f)* |
| 2nd pers. | tìwọ | *yours (m/f)* | 2nd pers. | tẹ̀yin | *yours (m/f)* |
| 3rd pers. | tòhun | *his/hers (m/f)* | 3rd pers. | tàwọn | *theirs (m/f)* |

Emphatic pronouns have possessive forms derived from being preceded by ‘ti’.

| | A | | B |
|---|---|---|---|
| èmi | ti + èmi | → | tèmi |
| ìwọ | ti + ìwọ | → | tìwọ |
| òun | ti + òun | → | tòun |
| àwa | ti + àwa | → | tàwa |
| ẹ̀yin | ti + ẹ̀yin | → | tẹ̀yin |
| àwọn | ti + àwọn | → | tàwọn |

Ti + emphatic subject pronouns above contract to become tèmi, tìwọ, etc.
Notice that in the column B, the low tone on the first vowel of the pronoun is retained.

Using possessive pronouns in sentences:

-Tìwọ ni aṣọ náà

-The cloth is yours

-Ìbídùn sọ pé tòun ni ìwé náà

- Ìbídùn said that the book is hers

-Tiwa ni ajá yẹn

-The dog is ours

 CC – 2011 The University of Texas at Austin

## Iṣẹ́ Ṣíṣe 1

Fi èyí tó bá yẹ dí àwọn àlàfo wọ̀nyí.
*Use the correct possessive pronoun in the blank space provided.*

1. _ni ìwé yẹn. (mine)
2. Aṣọ____________________wà ní orí ibùsùn. (yours pl.)
3. Àwọn ọmọ____________________wà ní ilé-ẹ̀kọ́ gíga. (ours)
4. Ìdánwòo____________________ń bẹ̀rẹ̀ ní ọ̀la. (yours sg.)
5. Nígbà wo ni____________________ń bẹ̀rẹ̀? (yours pl.)

## Iṣẹ́ Ṣíṣe 2


Fi èyí tó bá yẹ dí àwọn àlàfo wọ̀nyí.
*Use the correct possessive pronoun in the blank space provided.*

> **Bí àpẹẹrẹ:**
>
> Tèmi____________________ni ìwé yẹn (mine)

1. _ni ìwé yẹn (ours).
2. _ni ìwé yẹn (his/hers).
3. _ni ìwé yẹn (theirs).
4. _ni ìwé yẹn (yours pl.).
5. _ni ìwé yẹn (yours sg.).


# Lesson 2 - Ẹ̀kọ́ Kejì
## Parts of the body

Parts of the body 1 – Front view




 CC – 2011 The University of Texas at Austin

Parts of the body 2 – Back view




The interrogative **kí ni** followed by 'what to do with the parts of the body

| | | | |
|---|---|---|---|
| Kí ni a | = | Kí la | what do we…? |
| n | = | l | |

## Iṣẹ́ Ṣíṣe 1

Dárúkọ àwọn ẹ̀yà ara tí à ń lò láti ṣe àwọn nǹkan wọ̀nyí:
*Mention parts of the body that we use to do the following:*

1. Kí la fi ń ronú? ______
2. Kí la fi ń rìn? ______
3. Àwọn ẹ̀yà ara wo ni a/ la fi ń gbá bọ́ọ̀lù? ______
4. Kí la fi ń tẹ dùrù? ______
5. Kí ló wa ni òkè ọrùn? ______
6. Kí la fi ń sunkún? ______
7. Kí la fi ń rẹ́rìnín? ______
8. Kí la fi ń gbá tẹníìsì? ______
9. Kí la fi ń wo tẹlifíṣàn? ______
10. Kí la fi ń ríran? ______
11. Kí ló wa ni òkè orí?______
12. Kí la fi ń jẹun?______
13. Kí ló wa ni àárínin èjìká àti ọwọ́?______
14. Kí ló wà ní àárínin itan àti ẹsẹ̀?______
15. Kí la fi ń kọ̀wèé?______
16. Kí la fi ń fun fèrè?______
17. Kí la fi ń gbọ́rọ̀?______
18. Kí la fi ń gbóòórùn?______
19. Kí la fi ń fò?______
20. Kí la fi ń pàtẹ́wọ́?______
21. Kí la fi ń jà?______
22. Kí la fi ń sín?______
23. Kí la fi ń tọ́ nǹkan wò?______
24. Kí la fi ń sáré?______
25. Kí la fi ń kàwé?______

 CC – 2011 The University of Texas at Austin

## Iṣẹ́ Ṣíṣe 2

Sọ ohun tí à ń fi àwọn ẹ̀yà ara wọ̀nyí ṣe.
*State what we use these parts of the body for.*

**Bí àpẹẹrẹ:**

orókún: a fi ń kúnlẹ̀

1. ojú: ______
2. ẹnu: ______
3. etí: ______
4. ọwọ́: ______
5. orí: ______
6. imú: ______
7. ẹsẹ̀: ______
8. eyín: ______
9. ahọ́n: ______
10. apá: ______

 CC – 2011 The University of Texas at Austin

# Lesson 3 - Ẹ̀kọ́ Kẹta:
# Ìlera àti àìsàn *(Health and illness)*

## Ìwòsànan ayé àtijọ́

Kí ayé tó di ayé ọ̀làjú, ewé àti egbòogi jẹ́ ohun tí àwọn babańláa wa máa ń lò láti fi wo àrùn. Àwọn oníṣégùn máa ń lọ sí inú igbó láti já ewé. Ewé àti egbòogi ni wọ́n máa ń gbo pọ̀ láti fi ṣe ìtọ́jú àwọn ènìyàn. Ó ṣe pàtàkì láti mọ̀ wípé àwọn oníṣègùn máa ń lo agbára oríṣiríṣi láti mọ irú àrùn tí ó bá ń bá ènìyàn jà. Nítorí ìdí èyí, àwọn babaláwo máa ń dá ifá láti mọ irú àrùn ti ó ń ṣe ènìyàn. Iṣẹ́ ìṣègun jẹ́ iṣẹ àjogúnba. Púpọ̀ nínú àwọn oníṣègùn ni wọ́n ń jogún iṣẹ́ náa láti ọwọ́ àwọn babańláa wọn.

Àwọn Yorùbá ní ìgbàgbọ́ wípé ohun búburú ni àrùn jẹ́. Nítorí èyí ni wọ́n fi máa ń sọ wípé: "Ìlera ni oògùn ọrọ̀". Ìtumọ èyí ni wípé, ìlera ṣe pàtàkì fún iṣẹ́ àti ìdàgbàsókè ènìyàn àti ìlú. Oríṣiríṣi àrùn ni ó máa ń bá àwọn ènìyàn jà. Àwọn èyí tí ó wọ́pọ̀ ni ibàa jẹ̀dọ̀jẹ̀dọ̀, ibàa pọ́njúpọ́ntọ̀ àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Oríṣiríṣi ìtọ́jú ni ó wà fún oríṣiríṣi ènìyàn. Ìtọ́jú ọmọdé yàtọ̀ sí ìtọ́jú aboyún. Ìyá Àbíyè ni orúkọ tí wọ́n máa ń pe oníṣègùn aboyún. Púpọ̀ nínú àwọn Ìyá Àbíyè ni wọ́n máa ń bọ Òrìṣà Ọlọ́mọ bíi Ọ̀ṣun àti Ọya. Agbára omi àti ewé ni àwọn Ìyá Àbíyè máa ń lò láti gbẹ̀bí fun àwọn aboyún. Àwọn eléwé ọmọ ni àwọn obìnrin tí wọ́n ń sáábà máa ń ṣe ìtọ́jú ọmọ ìkókó. Oríṣiríṣi àgbo ni àwọn eléwé ọmọ máa ń kàpọ̀ láti fi ṣe ìtọ̀jú ọmọ ìkókó.

### Iṣẹ́ Ṣíṣe 1

Dáhùn àwọn ìbéèrè wọ̀nyí ní ẹ̀kúnrẹ́rẹ́.
*Answer the following questions in complete sentences.*

1. Kí ni àwọn Yorùbá máa fi ń ṣe ìtọ́jú aláìsàn kí ayé tó di ayé ọ̀làjú?
2. Ọ̀nà wo ni àwọn oníṣègún máa ń gbà mọ irú àrùn tí ó bá ń bá ènìyàn jà?
3. Kí ni ìgbàgbọ́ àwọn Yorùbá nípa àrùn?
4. Irú àwọn ènìyàn wo ni ó máa ń ṣe ìtọ́jú àwọn ọmọdé àti àwọn aboyún ni ayé àtijọ̀?
5. Bí àrùn bá kọjá nǹkan tí a kò lè lo egbòogi fún, kí ni ohun pàtàkì tí àwọn onìṣègùn máa ń ṣe?
6. Báwo ni púpọ̀ nínúu àwọn oníṣègùn ní ayé àtijọ́ ṣe máa ń di oníṣègùn?
7. Kí ni ohun pàtàkì tí àwọn tí ó ń ṣe ìtọ́jú àwọn aboyún àti ọmọdé máa ń lò látí ṣe ìtọjúu wọn?
8. Ṣe àlàyée gbólóhùn yìí, " Ìlera ni oògùn ọrọ̀".
9. Dárúkọ àwọn àrùn tí ó wọ́pọ̀ láàárín àwọn ọmọdé.
10. Àwọn wo ni wọ́n màa ń tọ́jú aláìsàn ní ayé àtijọ́?

 CC – 2011 The University of Texas at Austin

## Iṣẹ́ Ṣíṣe 2

Parí àwọn gbólóhùn wọ̀nyí.
*Complete the following sentences.*

1. Ní ayé àtijọ́, __________ ni àwọn ènìyàn máa ń lò fún ìwòsàn.
a. ewé
b. egbò
c. ewé àti egbò igi
d. ògùn òyìnbó

2. Àwọn _________ ni wọ́n máa ń ṣe ìṣègùn fún àwọn ènìyàn láyé àtijọ́.
a. oníṣègùn òyìnbó
b. oníṣègùn ìbílẹ̀
c. oníṣègùn àgbáyé
d. Babaláwo

3. Àwọn oníṣègùn láyé àtijọ́ máa ń kọ́ iṣẹ́ ìṣègùn lọ́wọ́ àwọn ___________.
a. oníṣègùn òyìnbó
b. oníṣègùn funfun
c. Babańláa wọn
d. ọ̀rẹ́

4. Ìlera ṣe _________ ní àwùjọ Yorùbá.
a. wúlò
b. pàtàkì
c. oníṣègùn
d. ìdàgbàsókè

5. ____________ ni ó ń gbẹ̀bí fún àwọn aláboyún.
a. Ìyá Àbíyè
b. Babaláwo
c. oníṣègùn òyìnbó
d. eléwé ọmọ

 CC – 2011 The University of Texas at Austin

## Ìwòsànan ti òde-òní

Àwọn òyìnbó amúnisìn ni wọ́n mú èto ìwòsàn ìgbàlódé wá sí ilẹ̀ẹ Yorùbá. Ilé ìwòsàn ìgbàlódé ni àwọn dókítà àti onímọ̀ ìṣègùn ti máa ń ṣe ìtọ́jú aláìsàn. Láti òkè òkun ni wọn ti máa ń kó awọn irin ìsẹ́ ti wọ́n ń lò wá.

Ìwòsàn òyìnbó yàtọ̀ sí ti àwọn babańlá àwọn Yorùbá ní ọ̀pọ̀lọpọ̀ ọ̀nà. Àwọn dókítà tàbí onímọ̀ ìṣègùn ní láti lọ sí ilé-ẹ̀kọ́ gíga láti kọ́ iṣẹ́ ìṣègùn kí wọ́n tó lè ṣe ìtọ́jú aláìsàn. Ọ̀pọ̀lọpọ̀ ọdún ni wọ́n sì máa ń lò kí wọ́n tó gba ìwé àṣẹ láti lè tọ́jú aláìsàn. Púpọ̀ nínúu wọn ni wọ́n máa ń fojú sí iṣẹ́ òbíi wọn láti kékeré.

Oríṣiríṣi onímọ̀ ìṣègùn òyìnbó ni ó wà. Àwọn apòògùn ni wọ́n mọ̀ nípa pípo oògùn àti bí awọn ènìyàn ṣe lè ra oògùn. Àwọn apòògùn náa máa ń lọ sí ilé-ẹ̀kọ́ gíga láti kọ́ iṣẹ́ ìṣègùn òyìnbó. Yàtọ̀ sí eléyìí, àwọn nọ́ọ̀sì ni àwọn obìnrin tàbí okùnrin tí ó máa ń ran dókítà lọ́wọ́ pẹ̀lú ìtọ́jú aláìsàn.

Oríṣiríṣi dókítà ni ó wà. Díẹ̀ nínúu wọn ni dókítà eléyin, oníṣẹ́ abẹ, dókítà ọmọdé, dókítà àrùn ọpọlọ, dókítà obìnrin tàbí aboyún, àti dókítà ojú. Ní ilé ìwòsàn òyìnbó, oríṣiríṣi ẹ̀ka ni ó wà. Àwọn ilé ìwòsàn tí ó tóbi máa ń ní ẹ̀ka bíi iṣẹ́ abẹ, ilé ìta òògùn àti ilé ìbímọ.

Àwọn ilé ìwòsàn ìjọba yàtọ̀ sí ti aládàáni. Dókítà aládàáni ní láti gba ìwé àṣẹ lọ́wọ́ ìjọba kí ó tó lè ṣe iṣẹ́ àrùn wíwò. Ṣùgbọ́n àwọn oníṣègùn ìbílẹ̀ kò ní láti gba ìwé àṣẹ kí wọ́n tó lè wo àìsàn.

### Iṣẹ́ Ṣíṣe 3

Dáhùn àwọn ìbéèrè wọ̀nyí ní ẹ̀kúnrẹ́rẹ́.
*Answer the following questions in complete sentences.*

1. Sọ fún wa ìyàtọ̀ tí ó wà láàárín ìwòsàn ní ayé àtijọ́ àti ti ayé òde-òní.
2. Àwọn wo ni ó mú ìwòsàn ìgbàlódé wá sí ilẹ̀ẹ Yorùbá?
3. Kí ni ìyàtọ̀ tí ó wà láàárín oníṣègùn ìbílẹ̀ àti ti òyìnbó?
4. Báwo ni ènìyàn ṣe lè di oníṣègùn òyìnbó?
5. Ǹjẹ́ ìyàtọ̀ wà láàárín ìmọ̀ ìṣègùn òyìnbó àti ti ìbílẹ̀? Dárúkọ oríṣi onímọ̀ ìṣègùn tí ó wá ní ayé òde òní.
6. Kí ni àǹfààní ìmọ̀ ìṣègùn òyìnbó ní òde-òní?
7. Dárúkọ ìrú àwọn dókítà tí ó wá nípa ìmọ̀ ìṣègùn òyìnbó?
8. Níbo ni àwọn irin iṣẹ́ fún ìwòsàn òyìnbò ti máa ń wá?
9. Kí ni àǹfààní tí ilé ìwòsàn òyìnbó tí ó bá tóbí ní?
10. Kí ni ìyàtọ̀ tí ó wà láàárín ilé ìwòsàn ìjọba àti tí aládàáni?

 CC – 2011 The University of Texas at Austin

## Iṣẹ́ Ṣíṣe 4


Mú èyí tó yẹ nínú àwọn wọ̀nyí sí ibi tó bá yẹ.

*Check the appropriate category for the following expressions.*

| Àwọn ọ̀rọ̀ | Ìwòsànan ti ayé átijọ́ | Ìwòsànan ti òde òní |
|---|---|---|
| 1. àgbo | ☐ | ☐ |
| 2. apòògùn | ☐ | ☐ |
| 3. babaláwo | ☐ | ☐ |
| 4. dókítà àrùn ọpọlọ | ☐ | ☐ |
| 5. dókítà obìnrin tàbí aboyún | ☐ | ☐ |
| 6. dókítà ojú | ☐ | ☐ |
| 7. dókítà ọmọdé | ☐ | ☐ |
| 8. dókítà eyín | ☐ | ☐ |
| 9. egbò igi/ egbòogi | ☐ | ☐ |
| 10. eléwé ọmọ | ☐ | ☐ |
| 11. ewé | ☐ | ☐ |
| 12. Ìyá Àbíyè | ☐ | ☐ |
| 13. nọ́ọ̀sì | ☐ | ☐ |
| 14. oníṣègùn aboyún | ☐ | ☐ |
| 15. oníṣẹ́ abẹ | ☐ | ☐ |

 CC – 2011 The University of Texas at Austin

## Ìsọ̀rọ̀ngbèsì *(Dialogue)*



*Jídé àti Túndé ǹ sọ̀rọ̀ nípa ìlera.*

| | |
|---|---|
| **Jídé:** | Túndé, ṣé wàá wá sí ilé-ìwé lọ́la? |
| **Túndé:** | Rárá o, nítorí pé araà mi kò yá. Orí ń fọ́ mi. Gbogbo ara ń ro mí. |
| **Jídé:** | Ṣé o ní ibà ni? |
| **Túndé:** | Ó dàbẹ́ẹ̀, ṣùgbọ́n n kò mọ̀. |
| **Jídé:** | Ṣébí tí o bá ní ibà, wà á kàn lọ rí dókítà ní ilé-ìwòsàn ìjọba ni. |
| **Túndé:** | Ǹjẹ́ o mọ̀ wípé n kò fẹ́ràn láti máa lọ sí ilé-ìwòsàn? Mo bẹ̀rù abẹ́rẹ́ púpọ̀. |
| **Jídé:** | Túndé, kì í ṣe gbogbo àìsàn ni ènìyàn ń gba abẹ́rẹ́ sí. Tí ó bá jẹ́ wípé ibà lásán ni, o lè mu àgbo. |
| **Túndé:** | Háà, èèmi, àgbo kẹ̀! Ki ní yẹn korò bíi ewúro. |
| **Jídé:** | Ṣebí kí àwọn òyìnbó tó dé, àgbo ni àwọn Yorùbá máa ń mu. |
| **Túndé:** | Àwọn Yorùbá ṣì ń mu àgbo títí dì ìsinyìí, ṣùgbọ́n èmi kọ́. Mà á kúkú lọ gba abẹ́rẹ́ yẹn ni! |
| **Jídé:** | Tí ojú, etí àti ẹsẹ̀ bá ń dùn ọ́ ń kọ́? |
| **Túndé:** | Fún ojú, màá lọ rí dókítà ojú ni. Ṣebí dókítà kò níí fún mi ní abẹ́rẹ́ nínú ojú! |
| **Jídé:** | Túndé, o kì í ṣe dókítà. |
| **Túndé:** | Bẹ́ẹ̀ ni, n kì í ṣe dókítà. Ǹjẹ́ o mọ̀ pé eyín ń dun èmi náà? |
| **Jídé:** | Háà! Wà á lọ rí yọyínyọyín (dókítà eyín) nìyẹn. Wọ́n á fún ẹ ní abẹ́rẹ́ nínú eyín. |
| **Túndé:** | Jọ̀ọ́ kúrò o jère. O dé nìyẹn. |

 CC – 2011 The University of Texas at Austin

## Iṣẹ́ Ṣíṣe 5

Dáhùn àwọn ìbéèrè wọ̀nyí ní ẹ̀kúnrẹ́rẹ́.
*Answer the following questions in complete sentences.*

1. Kí ni àrùn tí ó ń ṣe Túndé?
2. Kí ni àrùn tí ó ń ṣe Jídé?
3. Tí o bá ń ṣe àìsàn, kí ni o máa ṣe?
4. Kí ló dé tí Túndé fi sọ wí pé “jọ̀ ọ́ kúrò o jère”?
5. Ṣé àwọn Yorùbá kò mu àgbo mọ́?

## Iṣẹ́ Ṣíṣe 6

Wá àwọn ọ̀rọ̀ wọ̀nyí
*Look for these words in the puzzle below. Pay attention to the tones!*
**aboyún, àgbo, àrùn, dókítà, èjìká, ewé, nọ́ọ̀sì, oníṣègùn, iṣẹ́, ìlú**

| | | | | | | | | | | | | | | |
|---|---|---|---|---|---|---|---|---|---|---|---|---|---|---|
| a | i | l | u | a | g | b | o | e | w | e | à | b | u | o |
| b | b | a | b | r | o | n | o | o | s | i | d | e | u | n |
| o | g | o | e | u | f | d | ó | k | í | t | à | e | j | i |
| y | d | u | y | n | o | è | m | n | l | u | j | w | l | s |
| ú | b | à | d | ú | n | j | j | s | l | i | k | e | k | è |
| à | g | b | o | k | n | Ì | h | i | u | n | r | i | n | g |
| r | u | a | l | s | ẹ́ | k | ẹ́ | n | k | ú | n | k | ú | u |
| ù | k | t | d | o | k | à | s | w | n | à | g | ú | k | n |
| n | a | m | e | g | n | e | j | a | b | o | y | i | n | i |
| ọ́ | k | n | o | w | n | Í | g | é | n | ọ́ | ọ̀ | s | ì | ṣ |
| o | i | g | o | d | é | a | ṣ | ẹ́ | o | w | o | e | j | ẹ́ |
| s | s | i | ẹ́ | s | h | à | b | è | d | é | ì | é | w | a |
| i | e | d | a | b | ó | y | u | n | g | à | r | l | s | n |
| ó | g | ó | g | ó | i | à | d | à | n | ù | m | k | ú | à |
| n | o | o | ẹ́ | s | à | g | b | e | j | à | n | ẹ́ | n | ọ̀ |

 CC – 2011 The University of Texas at Austin

## Iṣẹ́ Ṣíṣe 7

Kọ ìtumọ̀ àwọn ọ̀rọ̀ wọ̀nyí sílẹ̀ ní èdèe Yorùbá.
*Write the meanings of these words in Yorùbá.*

1. aboyún ____________________
2. àgbo ____________________
3. àrùn ____________________
4. dókítà ____________________
5. èjìkà ____________________
6. ewé ____________________
7. nọ́ọ̀sì ____________________
8. onísègùn ____________________
9. iṣẹ́ ____________________
10. ìlú ____________________


CC – 2011 The University of Texas at Austin

# Lesson 4 - Ẹ̀kọ́ Kẹrin:
# Eré Ìdárayá *(Sports)*

## Eré Ìdárayá àtijọ

Oríṣi eré ìdárayá méjì ni ó wà: ti ìta gbangba àti ti abẹ́lé (abẹ ilé). Méjèèjì ni àwọn Yorùbá máa ń ṣe láyé àtijọ títí di òní. Eré ìdárayá abẹ́lé tí ó gbajúmọ̀ jù láàrín àwọn Yorùbá ni ayó títa. Tọmọdé tàgbà, tọkùnrin tobìnrin ní ó máa ń ta á. Oríṣiríṣi erémọdée Yorùbá tí ó jẹ ti ìta gbangba ni erée bojúbojú àti ẹkùn mẹ́ran. Ìjàkadì tàbí ẹkẹ ni eré ìta gbangba tí àwọn ọmọdé àti ọ̀dọ́ tí wọ́n lágbára máa ń ṣe látayé báyé.

A kò gbọ̀dọ́ gbàgbé àlọ́ pípa gẹ́gẹ́ bí oríṣi eréṣùpá (ere òṣùpá) kan. Ìyẹn ni pé lákòókò tí òṣùpá bá mọ́lẹ̀ rokoṣo ni wọ́n máa ń ṣe eré náà. Ní ìrú àkókò bẹ́ẹ̀, àgbàlagbà kan ni í máa kó àwọn ọmọdé jọ láti sọ̀tàn fún wọn. Orin, ijó, àti ìlù lílù pẹ̀lú àtẹ́wọ́ pípa ibẹ̀ a máa mú kí àwọn ọmọdé gbádùnun rẹ̀, a sì máa dá wọn lára ya dáradára.

### Iṣẹ́ Ṣíṣe 1

Dáhùn lóòótọ́ ni tàbí lóòótọ́ kọ́ fún àwọn ìbéèrè wọ̀nyí.
*Answer 'Yes' or 'No' to the following questions.*

| | | Òótọ́ ni | Òótọ́ kọ́ |
|---|---|---|---|
| 1. | Oríṣi eré ìdárayá mẹ́rin ni ó wà ní ayé àtijọ́. | ☐ | ☐ |
| 2. | Eré òde-òní ni ayò títa. | ☐ | ☐ |
| 3. | Àwọn àgbàlagbà nìkan ni wọ́n máa ń ta ayò. | ☐ | ☐ |
| 4. | Ọ̀sán ni wọ́n máa n pa àlọ́. | ☐ | ☐ |
| 5. | Ọmọ kékeré ni ó máa ń pa àlọ́ fún àwọn ẹgbẹ́ẹ rẹ̀. | ☐ | ☐ |

 CC – 2011 The University of Texas at Austin

## Iṣẹ́ Ṣíṣe 2

Parí àwọn gbólóhùn wọ̀nyí.
*Complete the following sentences.*

1. Oríṣi eré ìdárayá mélòó ni ó wá?
a. mẹ́ta
b. mẹ́rin
c. méjì
d. márùnún

2. Eré ìdárayá abẹ́lé tí ó gbajúmọ̀ jù láààrín àwọn Yorùbá ni __________?
a. gbígba bọ́ọ̀lù
b. ayó títa
c. wíwo tẹlifíṣàn
d. òkìtì títa

3. Eré ìdárayá àgbàlagba ni ________?
a. ìjàkadì
b. ẹkùn mẹ́ran
c. erée bojúbojú
d. ayó títa

4. Eré òṣùpá fún ọmọdé ni ___________?
a. ẹkùn mẹ́ran
b. àlọ́ pípa
c. ìjàkadì
d. erée bojúbojú

5. Ta ni ó lè ta ayò?
a. ọmọdé
b. ọkùnrin
c. obìnrin
d. gbogbo ènìyàn

 CC – 2011 The University of Texas at Austin

## Eré Ìdárayá òde-òní

Lóde-òní tí ọ̀làjú ti gbòde, eré ìdárayá abẹ́lé bíi lúdò àti káàdì gbajúmọ̀ púpọ̀púpọ̀. Oríṣiríṣi sì ni eré ìdárayá ìta gbangba lóde-òní. Lára wọn ni igi fífò, eré sísá, bọ́ọ̀lù àjùsáwọ̀n, bọ́ọ̀lù àfọwọ́gbá, ẹ̀ṣẹ́ jíjà àti bọ́ọ̀lù àfẹsẹ̀gbá. Bọ́ọ̀lù àfẹsẹ̀gbá ní ó gbajúmọ̀ jùlọ nínúu gbogbo àwọn eré òde-òní ní orílẹ̀-èdè Nàìjíríà. Agbábọ́ọ̀lù mọ́kànlá ni ó máa wà ní ọwọ́ ẹgbẹ́ agbábọ́ọ̀lù kan ní oríi pápá lákòókò ìdíje. Ẹgbẹ́ agbábọ́ọ̀lù méjì ni ó sì máa ń díje ní akókò ìṣeré. Nítorí náà agbábọ́ọ̀lù méjìlélógún ni àpapọ̀ gbogbo agbábọ́ọ̀lù tí wọ́n gbọ́dọ̀ wà lóríi pápá lákòókò ìdíje. Rẹfirí ni ẹnì kẹtàlélógún. Òun sì ni alábòójútó erée bọ́ọ̀lù àfẹsẹ̀gbá lóríi pápá. Ó sì máa ń ní olùránlọ́wọ́ méjì tí wọ́n máa ń dúró sí ẹ̀gbẹ̀ẹ́ pápá ìṣeré. A lè pè wọ́n ní olùrànlọ́wọ́ọ rẹfirí.

Lárá àwọn ẹgbẹ́ agbábọ́ọ̀lù tí ó lórúkọ ní orílẹ̀-èdè Nàìjíríà ni: Shooting Stars ti Ìbàdàn, Rangers International, Enyìmba Football Club ti Aba, Kano Pillars, Abiọla Babes àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Super Eagles ni ẹgbẹ́ agbábọ́ọ̀lù tí ó ń ṣojú orílẹ̀-èdè Nàìjíríà. Lára àwọn agbábọ́ọ̀lù tí wọ́n ti ṣe gudugudu méje àti yààyà mẹ́fà lóríi pápá tí wọ́n sì lórúkọ gidi ni Túndé Balógun, Ṣẹ́gun Ọdẹ́gbàmí, Ràṣídì Yẹ̀kínnì, Peter Rùfáí, Kanu Nwankwo, Babangida Babayaro, Sunday Oliseh, Taribo West, Daniel Amokachi, Victor Ikpeba Augustin Jay-jay Okocha àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ.

Awọn ẹgbẹ́ agbábọ́ọ̀lù Super Eagles kò kẹ̀rẹ̀ rárá. Káàkiri àgbáyé ni wọ́n ti mọ̀ wọ́n bí ẹni mowó. Àwọn ni wọ́n gba Ife ẹ̀yẹ ti àwọn orílẹ̀-èdè Adúláwọ̀ ní ọdúnun 1994 àti ìdíje ti Olíṅpîkì ní ọdúnun 1996.

### Iṣẹ́ Ṣíṣe 3

Dáhùn àwọn ìbéèrè wọ̀nyí.
*Answer the following questions.*

1. Dárúkọ eré ìdárayá mẹrin tí ó mọ̀ ní òde-òní.
2. Sọ ìyàtọ̀ tó wà láàárìnin bọ́ọ̀lù àjùsáwọ̀n àti bọ́ọ̀lù àfọwọ́gbá.
3. Ènìyàn mélòó ni wọ́n máa ń wà lóríi pápá ìṣeré fún bọ́ọ̀lù àfẹsẹ̀gbá?
4. Ṣé gbogbo ènìyàn ni wọ́n mọ ẹgbẹ́ agbábọ́ọ̀lùu Super Eagles?
5. Ṣé ẹgbẹ́ agbábọ́ọ̀lùu Super Eagles ni ó gba ife ẹ̀yẹ àgbáyé ni ọdúnun 1998?

 CC – 2011 The University of Texas at Austin

### Iṣẹ́ Ṣíṣe 4

Parí àwọn gbólóhùn wọ̀nyí.
*Complete the following sentences.*

1. Eré ìdárayá abẹlé òde-òní ni __________?
a. ayò
b. lúdò
c. eré sísá
d. igi fífò

2. Oríṣi eré ìdárayá ìta gbangba mélòó ni ó wá ni òde-òní nínú nǹkan tí a kà?
a. márùnún
b. mẹ́fà
c. méje
d. mẹ́rin

3. Eré ìdárayá òde-òní wo ló gbajúmọ̀ jùlọ ní orílẹ̀-èdè Nàìjíríà?
a. bọ́ọ̀lù àfọwọ́gbá
b. bọ́ọ̀lù àjùsáwọ̀n
c. ẹ̀ṣẹ́ jíjà
d. bọ́ọ̀lù àfẹsẹ̀gbá

4. Ènìyàn mélòó ni ó wá ní ẹgbẹ́ agbábọ́ọ̀lù kan?
a. méjìlélógún
b. mẹtàlélógún
c. mọ́kànlá
d. méjìlá

5. Olùránlọ́wọ́ mélòó ni rẹfirí máa ń ní nínú bọ́ọ̀lù àfẹsẹ̀gbá?
a. mẹ́rin
b. mẹ́ta
c. méjì
d. márùnún

 CC – 2011 The University of Texas at Austin

### Iṣẹ́ Ṣíṣe 5

Mú èyí tó yẹ nínú àwọn wọ̀nyí sí ibi tó bá yẹ.

*Check the appropriate category for the following expressions.*

| Àwọn ọ̀rọ̀ | | Eré Ìdárayá àtijọ | Eré Ìdárayá òde-òní |
|---|---|---|---|
| 1. | alábòójútó erée bọ́ọ̀lù | ☐ | ☐ |
| 2. | àfẹsẹ̀gbá/rẹfirí | ☐ | ☐ |
| 3. | àlọ́ pípa | ☐ | ☐ |
| 4. | bọ́ọ̀lù àjùsáwọ̀n | ☐ | ☐ |
| 5. | bọ́ọ̀lù àfọwọ́gbá | ☐ | ☐ |
| 6. | bọ́ọ̀lù àfẹsẹ̀gbá | ☐ | ☐ |

### Iṣẹ́ Ṣíṣe 6

Kọ ìtumọ̀ àwọn ọ̀rọ̀ wọ̀nyí sílẹ̀ ní èdèe Yorùbá.

*Write down the meanings of these words in Yorùbá.*

1. alábòójútó eré bọ́ọ̀lù àfẹsẹ̀gbá
2. bojúbojú
3. Ìjàkadì tàbí ẹkẹ
4. ìwẹ̀ wíwẹ̀
5. pápá ìṣeré

 CC – 2011 The University of Texas at Austin



# Chapter 9 - Orí Kẹsànán | MY WORK PLACE

## ***OBJECTIVES:***

In this chapter you will learn:

- How to describe different types of professions
- How to use future tense
- How to negate a sentence using ‘kò tí ì’
- How to identify types of professions

## Àwọn ọ̀rọ̀ (*Vocabulary*)

| Nouns | |
|---|---|
| adájọ́ | *judge* |
| àgbẹ̀ | *farmer* |
| agbẹjọ́rò | *lawyer* |
| akọ̀pẹ | *palm tree tapper* |
| alágbẹ̀dẹ | *blacksmith/goldsmith* |
| alápatà | *butcher* |
| aláró | *tie-dyer* |
| akọ̀wé | *secretary* |
| alájàpá | *person who travels with goods in a truck* |
| àṣeyọrí | *success* |
| awakọ̀ | *driver* |
| babaláwo | *Ifa priest/diviner* |
| daran-daran | *shepherd* |
| dókítà | *doctor* |
| ẹlẹ́ran | *meat seller* |
| géńdé | *adult* |
| ìránṣọ | *sewing* |
| ìyàtọ̀ | *difference* |
| jagunjagun/ajagun | *warrior/soldier* |
| méjéèjì | *both* |
| mẹkáníìkì | *mechanic* |
| nọ́ọ̀sì | *nurse* |
| oko | *farm* |
| olùkọ́ | *teacher* |
| onídìrí | *hair braider* |
| oníṣòwò | *trader* |
| oníròyìn | *newscaster, journalist* |
| oníwóróbo | *petty trader* |

| | |
|---|---|
| ọdẹ | *hunter* |
| ọlọ́pàá | *police officer* |
| ọ̀rẹ́ | *friend* |
| pẹjapẹja | *fisherman* |
| sáyẹ́ǹsì | *science* |

## Noun Phrases

| | |
|---|---|
| àtẹ títà | *display of goods for sale* |
| àwọn ti wọ́n  ní iṣẹ́ lọ́wọ́ | *those who are working* |
| àwọn tí wọ́n kàwé | *the educated* |
| dókítà ẹsẹ̀ | *podiatrist* |
| dókítà eyín | *dentist* |
| dókítà olùtọ́jú obìnrin | *gynecologist* |
| dókítà ọmọdé | *pediatrician* |
| igbó kìjikìji | *thick forest* |
| Ilé-ìwé olùkọ́ni àgbà | *College of Education* |
| Ilé-ìwé gbogbo-ǹ-ṣe | *Polytechnic* |
| Ilé-ìwé mẹ́wàá | *secondary school* |
| ìlú ńlá | *city/big town* |
| iṣẹ́ àbáláyé | *traditional profession* |
| Iṣẹ́ aṣerunlóge | *hair dresser* |
| Ìwé àṣẹ ìṣegùn òyìnbó | *Western medical certification* |
| ìwé kíkà | *studies* |
| kárà-kátà | *buying and selling/petty trading* |
| ohun tí ó wúlò | *something that is useful* |
| oògùn ìṣẹ́ | *remedy for poverty* |
| òwe Yorùbá | *Yorùbá proverb* |
| ọjà etílé | *town market* |
| ọjà eréko | *village market* |
| ọjọ́ iwájú | *(in )the future* |
| ọmọ kékeré | *a child* |

 CC – 2012 The University of Texas at Austin

| | |
|---|---|
| oníwé ìròyìn | *journalist/newspaper columnist* |
| ọ̀nà oríṣiríṣi | *different ways* |
| yunifásítì | *university* |
| Yunifásítì ìmọ̀ ẹ̀rọ | *University of Technology* |
| Yunifásítì ẹ̀kọ́ àgbẹ̀ | *University of Agriculture* |

## Verbs

| | |
|---|---|
| di/da | *to become* |
| gbà | *take* |
| gbayì | *honored/valued* |
| gbọ́dọ̀ | *must* |
| yàn | *to choose* |

## Verb Phrases

| | |
|---|---|
| bá fẹ́ | *like to* |
| dẹ̀gbẹ́ | *to hunt* |
| foju sí | *to observe* |
| gba ìwúre | *prayer for success* |
| gba ọdún púpọ̀ | *take several years* |
| gbé ìgbésẹ̀ | *take up the responsibility* |
| jẹ́ kí | *to allow/let* |
| kò burú | *that's fine* |
| kò kí ń sáábà | *it's not always* |
| kò tí ì di géńdé | *has not become an adult* |
| kọ́ iṣẹ́ | *to learn a trade* |
| máa ń di ipò pàtàkì mú | *to hold important positions* |
| máa ń pẹ́ láti gbà | *to take a long time to obtain* |
| múra | *hasten to* |
| parí | *to complete/to end* |
| pàtẹ irè oko | *to display farm products* |
| rẹ́ni (rí ẹni) | *to find or see someone* |
| rọ irin | *to melt metals* |


CC – 2012 The University of Texas at Austin

| | |
|---|---|
| ṣe àyẹ̀wo | *to take a look at* |
| sọ àkọsẹ̀jáyé ọmọ | *predict a child's future* |
| tẹ̀lé | *to follow* |
| wọ́ pọ̀ | *common* |
| yàn láàyò | *to favor by choice* |

## Adjectives

| | |
|---|---|
| bíi | *like* |
| léwu púpọ̀ | *to be very dangerous* |
| yìí | *this* |

## Adverbs

| | |
|---|---|
| gan-an ni | *very much /a lot* |
| nígbà mìíràn | *sometimes* |

## Prepositional phrases

| | |
|---|---|
| fún ìdàgbàsókè ìlú | *for the progress of the city/town/community* |
| jìnnà sí | *far from* |
| nípa ìgbésí ayé | *about life* |
| ní àwùjọ | *in the community* |
| ní òde-òní | *today* |
| súnmọ́ abà | *near the hut* |

## Other Expressions

| | |
|---|---|
| tí ó yẹ | *that is required (of them)* |

 CC – 2012 The University of Texas at Austin

## Lesson 1 - Ẹ̀kọ́ Kìíní:

## Verbs for professions

The following verbs are used for asking questions or talking about professions: jẹ́, dì/dà

**For example**:

Kí ni ìwọ fẹ́ dà? *What do you want to become?*

However, when you respond to the question, you use the verb **'dì'**.

**For example**:

Èmi fẹ́ di dókítà àrùn ọpọlọ.

The low tone in **'dì'** is dropped, becoming a mid tone when the verb is used in a sentence.

**For example**:

Bàbáa Jídé jẹ́ agbẹjọ́rò, ṣùgbọ́n Délé fẹ́ di ẹnjíníà lẹ́yìn ẹ̀kọ́ọ rẹ̀

Jídé's father is an attorney, but Délé wants to be an engineer following his studies

### Iṣẹ́ Ṣíṣe 1

Ó kàn ẹ. Sọ fún wa nǹkan tí àwọn òbí rẹ jẹ́, àti nǹkan tí ìwọ náá fẹ́ẹ́ dà.

*It's now your turn. Tell us about your parents' professions and what you want to become.*

### Ìsọ̀rọ̀ngbèsì *(Dialogue)*



Marcus ń sọ fùn Felicia ohun tí ó fẹ́ dà nígbà tí ó bá parí ẹ̀kọ́ọ rẹ̀.

*Marcus is telling Felicia what he wants to become when he completes his education*

 CC – 2012 The University of Texas at Austin

| | |
|---|---|
| **Marcus:** | Bàwo ni, Felicia? |
| **Felicia:** | Háà! Marcus, dáadáa ni. |
| **Marcus:** | Kí ní o wá ṣe ní láàbù? |
| **Felicia:** | Mo wá ṣe àyẹ̀wòo sámpùlù ni. |
| **Marcus:** | Hà! Hà! Ṣe ẹ̀kọ́ nípa sáyẹ́ǹsì ni iwọ náà ń kọ́ ni? |
| **Felicia:** | Bẹ́ẹ̀ni. Mo ń kọ́ nípa sáyẹ̀ǹsì. Bàọ́lọ́jì ni ẹ̀kọ́ọ̀ mi dálé lórí nítorí pé mà á fẹ́ di dókítà nígbà tí mo bá parí ẹ̀kọ́ọ̀ mi. |
| **Marcus:** | Ó dára bẹ́ẹ̀. Abájọ tí o fi tẹra mọ́ṣẹ́. Á á dára o! |
| **Felicia:** | Oo. O ṣé o Marcus. Kí ni ẹkọ́ọ tìrẹ dálé lórí ? |
| **Marcus:** | Mo kan ń ṣe iṣẹ́ kan tí ó jọmọ́ sáyẹ́ẹ̀ǹsì ni. Ẹ̀kọ́ nípa ìmọ̀-ẹ̀rọ ni ẹ̀kọ́ọ̀ mi dálé lórí. Mo fẹ́ràn ìmọ̀-ẹ̀rọ gan-an ni nítorí pé mà á fẹ́ di ẹnjiníà nígbà tí mo bá parí ẹ̀kọ́ọ̀ mi. |
| **Felicia:** | Iṣẹ́ ẹnjiníà náà dára púpọ̀, ṣùgbọ́n n kò lè ṣe é, nítorí pé mo fẹ́ràn iṣẹ́ẹ dókítà gan-an ni. |
| **Marcus:** | Kò burú. A jẹ́ wípé níwòyí ọdún márùnún, màá ti di ẹnjiníà. Ìwọ náà á ti di dókítà. Ó dàbọ̀ o. |
| **Felicia:** | Ó dàbọ̀ o, ẹnjiníа Marcus!!! |

## Iṣẹ́ Ṣíṣe 2

Dáhùn àwọn ìbéèrè wọ̀nyí.
*Answer the following questions.*

1. Ta ni Felicia àti Marcus?
2. Kí ni Marcus wá ṣe ní láàbù?
3. Kí ni Felicia fẹ́ dà?
4. Kí ni Marcus fẹ́ dà?
5. Kí ló dé tí àwọn méjèèji fi fẹ́ di nǹkan tí wọ́n fẹ́ dà?

 CC – 2012 The University of Texas at Austin

## Lesson 2 - Ẹ̀kọ́ Kẹta:
## Negation: kò tí ì (*has not*) / kò ì tí ì (*has not yet*)

Emphatic pronouns do not change with kò tí ì (has not).

**For example**:

| | |
|---|---|
| èmi kò tí ì | I have not |
| ìwọ kò tí ì | You (sg.) have not |
| òun kò tí ì | S/he has not |

### Regular pronouns + kò tí ì

| Singular | | | Plural | | |
|---|---|---|---|---|---|
| **1st pers.** | n kò tí ì | *I have not (m/f)* | **1st pers.** | a kò tí ì | *we have not (m/f)* |
| **2nd pers.** | o kò tí ì | *you have not (m/f)* | **2nd pers.** | ẹ kò tí ì | *you(pl.) have not (m/f)* |
| **3rd pers.** | kò tí ì | *s/he has not* | **3rd pers.** | wọn kò tí ì | *they have not (m/f)* |

### Regular pronouns + kò ì tí ì

Regular pronouns do not change whatsoever with ‘kò ì tí ì (has not yet).

**For example:**

| Singular | | | Plural | | |
|---|---|---|---|---|---|
| **1st pers.** | n kò ì tí ì | *I have not yet (m/f)* | **1st pers.** | a kò ì tí ì | *we have not yet (m/f)* |
| **2nd pers.** | o kò ì tí ì | *you have not (m/f)* | **2nd pers.** | ẹ kò ì tí ì | *you (pl.) have not yet(m/f)* |
| **3rd pers.** | kò ì tí ì | *s/he has not yet* | **3rd pers.** | wọn kò ì tí ì | *they have not yet (m/f)* |

 CC – 2012 The University of Texas at Austin

### Iṣẹ́ Ṣíṣe 1

Lo ‘**kò ì tí ì**’ láti fi yí àwọn gbólóhùn wọ̀nyí sí òdì.
*Use ‘**kò ì tí ì**’ to negate the following sentences.*

1. Olú ti jẹun. ______________________________
2. Mo ti lọ sí ibẹ̀. ______________________________
3. Ó ti sùn ______________________________
4. Èmi ti wẹ̀. ______________________________
5. Màmá Olú ti fọṣọ. ______________________________

### Iṣẹ́ Ṣíṣe 2

Tún àwọn gbólóhùn wọ̀nyí kọ ní èdè Yorùbá.
*Translate the following into Yorùbá.*

1. I have not yet started my homework assignment?
2. You have not yet finished your assignment.
3. She has not yet given birth.
4. We have not received our money.
5. You (pl.) have not found your bag?
6. They have not eaten their food.
7. It has not seen its shadow.
8. I have not gone there.
9. He has not yet finished reading the book.
10. I have not taken my exams.

# Lesson 3 - Ẹ̀kọ́ Kẹrin: Professions

## Cultural Vignette: Iṣẹ́ Àbáláyé (*Traditional Professions*)

Ní ilẹ̀ẹ Yorùbá, ọ̀nà orísìírísìí ni àwọn ènìyàn máa ń gbà láti mọ iṣẹ́ tí wọ́n bá fẹ́ yàn láàyò. Ìgbà mìíràn, àwọn òbí á lọ sí ilée babaláwo láti lọ ṣàyẹ̀wò. Babaláwo á sọ àkọsẹ̀jayé ọmọọ wọn fún wọn. Nínúu àkọsẹ̀jayé ni wọ́n á ti mọ iṣẹ́ tí ọmọ náà gbọ́dọ̀ ṣe.

Nígbà mìíràn, àwọn òbí máa ń jẹ́ kí ọmọ wọn jogún iṣẹ́ tí wọ́n bá ń ṣe. Bí àpẹẹrẹ, àwọn àgbẹ̀ máa ń jẹ́ kí àwọn ọmọ ọkùnrin wọn tẹ̀lé wọn lọ sí oko títí tí wọ́n á fi di géńdé. Tí ọmọ bá ti di géńdé, bàbá ọmọ áá ya oko fún un. Oko yíyà ṣe pàtàkì nínúu ìgbésí ayé ọmọ ọkùnrin. Ìdí èyí ni wí pé, tí wọ́n bá ti ya oko fún ọmọ, wọ́n ti fún ọmọ náà ní ohun tí ó nílò láti fi tọ́jú ìyàwó àtí ẹbíi tirẹ̀. Òwe Yorùbá kan sọ wí pé: “bí ọmọdé bá tó ó lọ́kọ́, ó ní láti lọ́kọ́ ni.” Ìtumọ̀ eléyìí ni wípé, ènìyàn kò gbọdọ̀ fi ẹ̀tọ́ dun ọmọdé tí o bà tí dàgbà.

Àwọn ọdẹ àti alágbẹ̀dẹ náà máa ń jẹ́ kí àwọn ọmọọ wọn fi ojú sí iṣẹ́ tí wọ́n bá ń ṣe. Tí ènìyàn bá dé ìbi tí àlágbẹ̀dẹ ti ń rọ irin, ènìyàn á bá ọ̀pọ̀lọpọ̀ ọmọ kékeré pẹ̀lúu wọn. Púpọ̀ nínú àwọn ọmọ yìí ni wọ́n jẹ́ ọmọọ wọn. Àwọn ọdẹ náà máa ń jẹ́ kí àwọn ọmọọ wọn tẹ̀lé wọn lọ sí ibi tí wọ́n ti ń dẹ̀gbẹ́. Ṣùgbọ́n wọn kì í sáábà jẹ́ kí wọ́n tẹ̀lé wọn lọ sí inú igbó kìjikìji. Igbó kìjikìji léwu púpọ̀ fún àwọn ọmọ kékeré tí wọn kò tîì di géńdé.

Ní ilẹ̀ẹ Yorùbá, kárà-kátà ni àwọn obìnrin sáábà máa ń ṣe jù. Gẹ́gẹ́ bí àwọn ọmọ ọkùnrin, àwọn ọmọ obìnrin náà máa ń tẹ̀lé màmáa wọn lọ sí ọjà. Oríṣi ọjà méjì ló wà ní ilẹ̀ẹ Yorùbá. Ọjà etílé àti ọjà eréko. Ọjà etílé ni àwọn ọjà tí ó súnmọ́ abà tàbí ìlú. Ọjà eréko ni àwọn ọjà tí wọ́n máa ń pàtẹ nǹkan oko. Ọjà eréko sáábà máa ń jìnnà sí ìlú. Ó ṣe pàtàkì fún àwọn ọmọbìnrin láti fojú sí iṣẹ́ẹ màmáa wọn. Ìdí èyí ni wí pé, iṣẹ́ ṣíṣe wà lára àwọn ọ̀nà tí Yorùbá máa ń gbà láti fi kọ́ àwọn ọmọọ wọn nípa bí wọn ṣe lè gbé ìgbésí àyée wọn. Ọmọ tí ó bá fojú sí iṣẹ́ àwọn òbíi rẹ, áá gba ìwúre. Ìwúre jẹ́ àdurà tí àwọn òbí máa ń ṣe fún ọmọ láti ṣe oríire àti àṣeyọrí nínú nǹkan tí ọmọ bá dáwọ́lé.

 CC – 2012 The University of Texas at Austin

## Iṣẹ́ Ṣíṣe 1

Dáhùn àwọn ìbéèrè wọ̀nyí.
*Answer the following questions.*

1. Báwo ni àwọn Yorùbá ṣe máa ń mọ irú iṣẹ́ tí àwọn ọmọọ wọn gbọ́dọ̀ yàn láàyò?
2. Ọ̀nà wo ni àwọn ọmọ lè gbà láti ṣe iṣẹ́ tí àwọn bàbáa wọn bá ń ṣe tí wọ́n bá dàgbà?
3. Irú oríṣì iṣẹ́ ìbílẹ̀ pàtàkì mélòó ni a kà nínú ìwé pé àwọn ọmọ ọkúnrin lè jogún látí ọwọ́ àwọn bàbáa wọn? Dárúkọ wọn.
4. Kí ni ìdí rẹ̀ ti oko yíyàn fi ṣe pàtàkì nínú ìgbésí ayé ọmọ ọkùnrin?
5. Kí ni ìdí rẹ̀ tí àwọn ọ̀dẹ kì í fí sáábà jẹ́ kí àwọn ọmọ wọn tẹ̀lé wọn lọ dẹ̀gbẹ́ nínú igbó kìjikìji?
6. Dárúkọ iṣẹ́ tí àwọn obìnrin Yorùbá máa ń sáábà ṣe jù.
7. Báwo ni àwọn ọmọ obìnrin ní ilẹ̀ Yorùbá ṣe máa ń kọ́ iṣẹ́ yìí láti ọ̀dọ̀ àwọn màmáa wọn?
8. Irú oríṣì ọjà mélòó ni a dàrúkọ pé ó wà ní ilẹ̀ẹ Yorùbá? Dárúkọ wọn.
9. Kí ní ìyàtọ̀ tí ó wà láàárín àwọn ọjà wọ̀nyí?
10. Kí ni pàtàkì iṣẹ́ ṣíṣe nínú ìgbésí ayè àwọn ọmọ Yorùbá?

## Iṣẹ́ Òde-Òní (*Modern Professions*)

Ní òde-òní, àwọn ènìyàn máa ń kọ́ iṣẹ́ lóríṣiríṣi. Púpọ̀ nínúu iṣẹ́ yìí wọ́pọ̀ láàárín àwọn tí wọ́n ń gbé ní ìlú ńlá bíi Èkó (Lagos) Ìbàdàn, Ògbómọ̀ṣọ́, Ẹdẹ, Òṣogbo àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Àwọn ènìyàn máa ń kọ́ iṣẹ́ bí i iṣẹ́ awakọ̀, alápatà, mẹkáníîkì, iṣẹ́ aṣọ rírán àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Ọ̀pọ̀lọpọ̀ ọdún ni àwọn ènìyàn máa ń lò láti fi kọ́ iṣẹ́ yìí. Kò kí ń pẹ́ tí àwọn ènìyàn fi máa ń mọ iṣẹ́ bíi awakọ̀ọ̀ ṣe. Nígbà mìíràn, iṣẹ́ẹ mẹkáníîkì máa ń gba ọ̀pọ̀lọpọ̀ ọdún láti kọ́. Iṣẹ́ aṣerunlóge àti àtẹ títà sáàbà máa ń jẹ́ iṣẹ́ obìnrin.

Ọ̀nà mìíràn tí àwọn Yorùbá tún máa ń gbà kọ́ṣẹ́ ni ilé-ìwé lílọ. Oríṣirísi ilé-ìwé ló wà: Ilé-ìwé alákọ̀ọ́bẹ̀rẹ̀, Ilé-ìwé mẹwáà àti ilé-ìwé gíga. Oríṣiriṣi yunifásítì ni ó wà ní ilẹ̀ẹ Yorùbá. Àwọn yunifásítì kan wà fún ẹ̀kọ́ àgbẹ̀. Àwọn kan sì wà fún ẹ̀kọ́ imọ ẹ̀rọ, Ilé-ìwé olùkọ́ni àgbà ni àwọn tí ó bá fẹ́ ṣe iṣẹ́ olùkọ́ máa ń lọ. Ilé-ìwé gbogbo-ǹ-ṣe ni ó wà fún àwọn ènìyàn tí ó bá fẹ́ kọ́ ẹ̀kọ́ ìmọ̀-ẹ̀rọ àti sáyẹ́nsì.

Àwọn tí ó bá lọ sí ilé-ìwé gíga ni wọ́n máa ń di adájọ́, dókítà, olùkọ́ àti akọ̀wé ìjọba. Ọ̀pọ̀lọpọ̀ ọdún ni àwọn ènìyàn máa ń lò láti fi kọ́ ẹ̀kọ́ nípa iṣẹ́ tí wọ́n bá fẹ́ yán láàyò ní ọjọ iwáju. Iṣẹ́ẹ dókítà máa ń gbà ọdún púpọ̀ ganan ni. Ìwé àṣẹ ìṣègùn òyìnbó máa ń pẹ́ láti gbà. Ní òde-òni, ìwé kíkà gbayì débi wípé gbogbo òbí ni ó fẹ́ rán ọmọ wọn lọ sí ilé-ìwé nítorí pé àwọn tí wọ́n lọ sí ilé-ìwé ni wọ́n máa ń di ipò pàtàkì mú ní àwùjọ. Ó ṣe pàtàkì kí awọn tí ó kàwé àti àwọn ti wọ́n ní iṣẹ́ lọ́wọ́ gbé ìgbésẹ̀ tí ó yẹ fún ìdàgbàsókè ìlú.

 CC – 2012 The University of Texas at Austin

### Iṣẹ́ Ṣíṣe 2

Dáhùn àwọn ìbéèrè wọ̀nyí.
*Answer the following questions.*

1. Irú àwọn iṣẹ́ wo ni àwọn Yorùbá máa ń kọ́ ní ayé òde-òní?
2. Kí ni ìyàtọ̀ tí ó wá láàárín iṣẹ́ ní ayé àtijọ́ àti ní ayé òde-òní?
3. Kí ni ìyàtọ̀ pàtàkì tí ó wá láàárín iṣẹ́ ọwọ́ kíkọ́ àti ìwé kíkà?
4. Ilé-ìwé wo ni ó yẹ kí àwọn ènìyàn lọ kí wọ́n tó lè fi ìwé kíkà ṣiṣẹ́ jẹun?
5. Oríṣì Yunifásítì mélòó ni a dárúkọ? Dárúkọ wọn.
6. Ǹjẹ́ ó ṣe é ṣe fún ènìyàn láti kọ́ ẹ̀kọ́ nípa iṣẹ́ àgbẹ̀ ní ilé-ìwé ní òde-òní? Kí ni ìdí fún ìdáhùn rẹ?
7. Irú iṣẹ́ wo ni ẹni tí ó bá lọ sí Yunifásítì lè ṣe?
8. Iṣẹ́ wo ni ó gba ọ̀pọ̀lọpọ̀ ọdún láti kọ́?
9. Kí ni pàtàkì ìwé kíkà fún ènìyàn tí ó bá lọ sí ilé-ìwé tí ó sì kàwé yanjú?
10. Irú ìhà wo ni àwọn òbí kọ sí ìwé kíkà fún àwọn ọmọọ wọn ni òde-òní?


CC – 2012 The University of Texas at Austin

## Iṣẹ́ Ṣíṣe 3

Mú èyí tó yẹ nínú àwọn wọ̀nyí sí ibi tó bá yẹ.

*Check the appropriate category for the following expressions.*

| Àwọn ọ̀rọ̀ | Iṣẹ́ Àbáláyé | Iṣẹ́ òde-òní |
|---|---|---|
| adájọ́ | ☐ | ☐ |
| àgbẹ̀ | ☐ | ☐ |
| agbẹjọ́rò | ☐ | ☐ |
| akọ̀pẹ | ☐ | ☐ |
| alágbẹ̀dẹ | ☐ | ☐ |
| alápatà | ☐ | ☐ |
| aláró | ☐ | ☐ |
| akọ̀wé | ☐ | ☐ |
| babaláwo | ☐ | ☐ |
| daran-daran | ☐ | ☐ |
| dókítà eyín | ☐ | ☐ |
| dókítà ẹsẹ̀ | ☐ | ☐ |
| dókítà obìnrin | ☐ | ☐ |
| dókítà ọmọdé | ☐ | ☐ |
| jagunjagun | ☐ | ☐ |
| mẹkáníìkì | ☐ | ☐ |
| nọ́ọ̀sì | ☐ | ☐ |
| olùkọ́ | ☐ | ☐ |
| onídìrí | ☐ | ☐ |
| oníròyìn | ☐ | ☐ |

 CC – 2012 The University of Texas at Austin

## Iṣẹ́ Ṣíṣe 4

Wá àwọn ọ̀rọ̀ wọ̀nyí

*Look for these words in the puzzle below. Pay attention to the tones!*

**adájọ́, àgbẹ̀, agbẹjọ́rò, akọ̀pẹ, aláró, awakọ̀, ẹlẹ́ran, géńdé, ìyàtọ̀, ọlọ́pàá**

| | | | | | | | | | | | | | | |
|---|---|---|---|---|---|---|---|---|---|---|---|---|---|---|
| a | d | a | g | b | a | k | ọ̀ | p | ẹ | ì | ẹ | a | l | ọ̀ |
| d | e | ń | g | e | ẹ́ | l | e | r | a | n | l | w | ọ | l |
| a | g | b | é | b | ì | l | a | r | ì | a | ẹ | a | l | o |
| j | o | u | ń | a | e | o | à | l | g | k | t | k | ọ́ | u |
| o | s | o | d | u | d | J | l | s | á | u | i | ọ̀ | p | g |
| i | d | u | é | d | u | d | o | ọ́ | a | r | n | b | à | e |
| j | a | d | a | d | á | J | ọ́ | r | p | b | ó | o | á | n |
| a | l | g | e | n | b | I | à | a | ọ̀ | a | i | ì | r | d |
| k | a | y | b | ẹ | a | à | y | g | t | a | à | y | o | é |
| u | r | ẹ | d | ẹ | l | w | l | a | b | i | g | à | j | o |
| m | o | m | o | i | j | ẹ́ | a | a | t | a | b | t | ọ̀ | l |
| o | l | o | r | a | b | ọ́ | r | k | k | o | ẹ̀ | ọ̀ | b | o |
| i | g | a | b | i | l | a | r | a | o | u | d | u | g | g |
| a | g | b | e | f | à | a | j | ọ̀ | n | o | r | i | a | b |
| a | k | ẹ̀ | a | k | o | p | e | a | b | a | l | e | d | ẹ |

 CC – 2012 The University of Texas at Austin

## Iṣẹ́ Ṣíṣe 5

Kọ ìtumọ̀ àwọn ọ̀rọ̀ wọ̀nyí sílẹ̀ ní èdèe Yorùbá.
*Write down the meaning of the following words in Yorùbá.*

1. adájọ́ ______________________
2. àgbẹ̀ ______________________
3. agbẹjọ́rọ̀ ______________________
4. akọ̀pẹ ______________________
5. aláró ______________________
6. awakọ̀ ______________________
7. ẹlẹ́ran ______________________
8. géńdé ______________________
9. Ìyàtọ̀ ______________________
10. ọlọ́pàá ______________________

 CC – 2012 The University of Texas at Austin



# Chapter 10 - Orí Kẹ̀wàá | HOME SWEET HOME!

## *OBJECTIVES:*

In this chapter you will learn:

- About ordinals
- How to use reflexives
- Vowel assimilation, vowel lengthening and vowel deletion
- About old and new forms of housing
- About your house

## Àwọn ọ̀rọ̀ (*Vocabulary*)

| Nouns | |
|---|---|
| ààfin | *palace* |
| abẹ | *razor* |
| afínjú | *clean (person)* |
| alákọ̀wé | *educated person* |
| àtíkè (páúdà) | *powder* |
| adìẹ | *chicken* |
| àga onítìmùtìmù | *sofa* |
| àjà | *story (house levels)* |
| àlejò | *guest* |
| amọ̀ | *clay* |
| aṣọ ìnura (táwẹ̀ẹ̀lì) | *towel* |
| àwùjọ | *a gathering (of people)* |
| àwòrán | *picture* |
| ayálégbé | *tenant* |
| balùwẹ̀ | *bathroom* |
| búlọ́ọ̀kù | *cement* |
| dìódóráǹtì | *deodorant* |
| èékánná | *nails* |
| ehoro | *rabbit* |
| ẹ̀dá ènìyàn | *human beings* |
| fèrèsé/wíńdò | *window* |
| fọ́sẹ́ẹ̀tì | *faucet* |
| fúláàtì | *apartment / flat* |
| gbajúmọ̀ | *important* |
| góòlù | *gold* |
| ibi | *place* |
| ibùsùn/bẹ́ẹ̀dì | *bed* |
| ìdọ̀tí | *dirt* |
| igi ìfọyín/búrọ́ọ̀ṣì | *toothbrush* |
| ìkángun | *one end of the house* |
| ìkáṣọsí/kọ́bọ́ọ̀dù | *closet* |
| ilé ìgbọ̀nsẹ̀ | *toilet* |
| ìlera | *good health* |

| | |
|---|---|
| ìlú òkèèrè | *foreign country* |
| ìmọ́tótó | *cleanliness* |
| ìpara | *body lotion* |
| ìrọ̀rí | *pillow* |
| iyanrìn | *sand* |
| jíígí | *mirror* |
| kábínẹ́ẹ̀tì | *cabinet* |
| kàhìnkàhìn | *sponge* |
| kápẹ́ẹ̀tì | *carpet* |
| kóòmù | *comb* |
| máràṣáná | *'don't buy matches' (it's a type of window)* |
| mèremère | *precious things* |
| míṣánnárì | *missionary* |
| mọlé-mọlé | *brick layer* |
| ògiri | *wall* |
| ojúlé | *room* |
| ọgbà | *yard* |
| ọ̀lẹ/ ìmẹ́lẹ́ | *laziness* |
| ọṣẹ ìfọyín (péèstì) | *toothpaste* |
| pálọ̀ | *living room* |
| pákò/orín | *chewing stick* |
| rédíò | *radio* |
| sîǹkì | *sink* |
| tíṣù | *tissue* |
| tòlótòló | *turkey* |
| tọ́ọ̀bù | *bathtub* |

## Noun Phrases

| | |
|---|---|
| apẹ̀ẹ̀rẹ̀ híhun | *basket weaving* |
| àsìkòo fọ́ọ̀lù | *fall season* |
| àsìkòo sípíríǹgì | *spring season* |
| àsìkòo sọ́mà | *summer season* |
| àsìkòo wíńtà | *winter season* |
| aṣọ òkè híhun | *traditional Yoruba cloth weaving* |
| aṣọ pípa láró | *tie-dying* |
| ènìyàn mímọ̀ | *familiar face* |

| | |
|---|---|
| ẹní híhun | *mat weaving* |
| ẹ̀yìn fífọ̀ | *palm oil extraction* |
| igun ilé | *one angle/corner of the house* |
| ilé alámọ̀ | *brick house* |
| ilée onísìmẹ́ǹtì | *house built with cement* |
| ilé ìgbọ̀nsẹ̀ | *toilet* |
| ìlẹ̀kẹ̀ sínsín | *bead-making* |
| ìyá àgbà | *old woman* |
| omi gbígbóná | *hot water* |
| omi tútù | *cold water* |
| ọṣẹ ìfọwọ́ | *hand soap* |
| ọṣẹ ìfọrun (ṣampú) | *shampoo* |
| ọṣẹ ìwẹ̀ | *bath soap* |

## Verb

| | |
|---|---|
| kórira | *to dislike* |

## Verb Phrases

| | |
|---|---|
| tẹpá mọ́ṣẹ́ | *to be hardworking* |

## Adjectives

| | |
|---|---|
| tẹ́jú | *spacious* |
| tónítóní | *stainless* |

 CC – 2011 The University of Texas at Austin

# Lesson 1 - Ẹ̀kọ́ Kìíní
## Ordinals

Remember in Chapter Four, Lesson 1, we compared numbers and cardinals as found below:

| Numbers | Cardinals | English |
|---|---|---|
| oókan | kan | *one* |
| eéjì | méjì | *two* |
| ẹ́ẹ́ta | mẹ́ta | *three* |
| ẹ́ẹ́rin | mẹ́rin | *four* |
| aárùnún | márùnún | *five* |
| ẹ́ẹ́fà | mẹ́fà | *six* |
| eéje | méje | *seven* |
| ẹ́ẹ́jọ | mẹ́jọ | *eight* |
| ẹ́ẹ́sànán | mẹ́sànán | *nine* |
| ẹ́ẹ́wàá | mẹ́wàá | *ten* |
| oókànlá | mọ́kànlá | *eleven* |
| eéjìlá | méjìlá | *twelve* |

(where eéjìlá implies ‘twelve’ and ìwé méjìlá implies ‘twelve books’)

| Ordinals | |
|---|---|
| ìkíní | *first* |
| ìkejì | *second* |
| ìkẹta | *third* |
| ìkẹrin | *fourth* |
| ìkarùnún | *fifth* |
| ìkẹfà | *sixth* |
| ìkeje | *seventh* |
| ìkẹjọ | *eighth* |
| ìkẹsànán | *ninth* |
| ìkẹwàá | *tenth* |
| ìkọkànlá | *eleventh* |
| ìkejìlá | *twelfth* |

Like cardinals, ordinals are placed after their nouns. However, since vowel deletion is very common in Yorùbá language, the initial **/i/** of the ordinal is deleted when the above ordinals are used as qualifiers as found below.

**For example:**

| Ordinals | |
|---|---|
| ọjọ́ kìíní | *first day* |
| ọjọ́ kẹrin | *fourth day* |
| ọjọ́ kẹ̀rìnlá | *fourteenth day* |
| ọjọ́ karùndínlógún | *fifteenth day* |
| ọjọ́ kẹ̀rìndínlógún | *sixteenth day* |
| ọjọ́ kẹtàdínlógún | *seventeenth day* |
| ọjọ́ kejìdínlógún | *eighteenth day* |
| ọjọ́ kọkàndínlógún | *nineteenth day* |
| ogúnjọ́ | *twentieth day* |

The table below compares the numbers to the cardinals, and the cardinals to the ordinals.

| Numbers | Cardinals | Ordinals |
|---|---|---|
| oókan | kan | ìkíní |
| eéjì | méjì | ìkejì |
| ẹ́ẹ́ta | mẹ́ta | ìkẹta |
| ẹ́ẹ́rin | mẹ́rin | ìkẹrin |
| aárùnún | márùnún | ìkarùnún |
| ẹ́ẹ́fà | mẹ́fà | ìkẹfà |
| eéje | méje | ìkeje |
| ẹ́ẹ́jọ | mẹ́jọ | ìkẹjọ |
| ẹ́ẹ́sànán | mẹ́sànán | ìkẹsànán |
| ẹ́ẹ́wàá | mẹ́wàá | ìkẹwàá |
| oókànlá | mọ́kànlá | ìkọkànlá |
| eéjìlá | méjìlá | ìkejìlá |

## Iṣẹ́ Ṣíṣe 1

Kí ni àwọn ọjọ́ wọ̀nyí ni Yorùbá?
*Provide the Yorùbá equivalents of the following.*

**Bí àpẹẹrẹ:**

7th day = Ọjọ́ keje

1. 21st day = ______
2. 15th day = ______
3. 6th day = ______
4. 18th day = ______
5. 3rd day = ______
6. 11th day = ______
7. 2nd day = ______
8. 50th day = ______
9. 37th day = ______
10. 1st day = ______

 CC – 2011 The University of Texas at Austin

## Iṣẹ́ Ṣíṣe 2

Dáhùn àwọn ìbèérè wọ̀nyí ní ẹ̀kúnrẹ́rẹ́.

*Answer the following questions in complete sentences.*

1. Ọjọ́ wo ni ọjọ́ kìíní oṣù kẹta ọdún yìí?

   ____________________

2. Ọjọ́ wo ni ọjọ́ kejìdínlógún oṣù kejì ọdún yìí?

   ____________________

3. Ọjọ́ wo ni ọjọ́ kọkàndínlógún oṣù kẹrin ọdún yìí?

   ____________________

4. Ọjọ́ wo ni ọjọ́ kejìlá oṣù kẹfà ọdún yìí?

   ____________________

5. Ọjọ́ wo ni ọjọ́ kẹtàlélógún oṣù kejọ ọdún yìí?

   ____________________

 CC – 2011 The University of Texas at Austin

## Iṣẹ́ Ṣíṣe 3

Kọ àwọn ọjọ́ wọ̀nyí ní Yorùbá.
*Write the following dates in Yorùbá.*

**Bí àpẹẹrẹ:**

1st January

ọjọ́ kìíní, oṣù kìíní ọdún

1. 17th September
2. 21st November
3. 9th July
4. 31st March
5. 11th April
6. 23rd May
7. 18th October
8. 3rd August
9. 10th June
10. 20th February

 CC – 2011 The University of Texas at Austin

## Iṣẹ́ Ṣíṣe 4

Kọ àwọn ọjọ́ ọ̀sẹ̀ wọ̀nyí ní Yorùbá.
*Write the following days of the week in Yorùbá (using the workday system).*

**Bí àpẹẹrẹ:**

Ọjọ́ kìíní ọ̀sẹ̀ = Ọjọ́ ajé

1. Ọjọ́ kéjì ọ̀sẹ̀ = ____________________
2. Ọjọ́ kẹ́ta ọ̀sẹ̀ = ____________________
3. Ọjọ́ kẹ́rin ọ̀sẹ̀ = ____________________
4. Ọjọ́ karùnún ọ̀sẹ̀ = ____________________
5. Ọjọ́ kẹfà ọ̀sẹ̀ = ____________________
6. Ọjọ́ keje ọ̀sẹ̀ = ____________________

## Iṣẹ́ Ṣíṣe 5

So àwọn tí ó bara mu ni ọ̀wọ́ A àti ọ̀wọ́ B papọ̀.
*Match the words in column A with those in column B.*

| A | B |
|---|---|
| ọjọ́ ẹtì | Sunday |
| ọjọ́ abámẹ́ta | Monday |
| ọjọ́bọ̀ | Friday |
| ọjọ́rú | Saturday |
| ọjọ́ ìṣẹ́gun | Thursday |
| ọjọ́ àìkú | Wednesday |
| ọjọ́ ajé | Tuesday |

 CC – 2011 The University of Texas at Austin

## Iṣẹ́ Ṣíṣe 6

So àwọn tí ó bara mu ni ọ̀wọ́ A àti ọ̀wọ́ B papọ̀.
*Match the words in column A with those in column B.*

| A | B |
|---|---|
| Ogún òkè | 6 books |
| Ọdún kejìlá | 12 years |
| Ìwé mẹ́fà | 20 floors |
| Òkè ogún | 6th book |
| Ọdún méjìlá | 12th year |
| Ìwé kẹfà | 20th floor |

 CC – 2011 The University of Texas at Austin

## Lesson 2 - Ẹ̀kọ́ Kejì:
## Reflexives - Vowel Assimilation,
## Vowel Lengthening, and Vowel Deletion

Reflexives denote what you do by yourself or for yourself as opposed to someone doing it for you. In order to state the former, you use **'fúnrara'** followed by a possessive pronoun as found below:

| | |
|---|---|
| fúnraraà mi | fúnraraa wa |
| fúnraraà rẹ | fúnraraa yín |
| fúnraraa rẹ̀ | fúnraraa wọn |

**For example:**

Mo ya irunùn mi fúnraraà mi. *I combed my hair myself.*

**Compare to:**

Màmáà mi ya irunùn mi fún mi. My mother combed my hair for me.
Or
Màmáà mi bá mi ya irunùn mi. My mother helped me comb my hair.

### Iṣẹ́ Ṣíṣe 1

Parí àwọn gbólóhùn wọ̀nyìí.
*Complete the following sentences with the appropriate reflexive.*

1. Èmi ń wẹ̀ ______________________
2. Òun ń fọ ẹnu ______________________
3. Àwa ń para ______________________
4. Àwọn ń bọ́jú______________________
5. Ó ń fọ eyín ______________________
6. Mò ń ya irun ______________________
7. À ń fọ ojú ______________________
8. Àwọn ọkùnrin ń fá irùgbọ̀n ______________________
9. Àwọn obìnrin ń kun ètè ______________________
10. Wọ́n ń fọ ọwọ́ ______________________

 CC – 2011 The University of Texas at Austin

## Iṣẹ́ Ṣíṣe 2

Ṣe àwọn nǹkan wọ̀nyì.
*Demonstrate the following gestures.*

1. Mo ń fọ eyìnìn mi **fúnraraà mi.**
2. O ń ya irunùn rẹ **fúnraraà rẹ.**
3. Ó ń fá irùngbọ̀nọn rẹ̀ **fúnraraa rẹ̀.**
4. A ń fọ ọwọ wa **fúnraraa wa.**
5. Ẹ ń pa ara yín **fúnraraa yín.**
6. Wọ́n ń nu ọwọ́ọ wọn **fúnraraa wọn.**

## Iṣẹ́ Ṣíṣe 3

Lo àpẹẹrẹ yìí láti fi dáhùn àwọn ìbéèrè wọ̀nyí.
*Use this example to answer the following questions.*

**Bí àpẹẹrẹ:**

Túndé/ eyín → Túndé, fọ eyínìn rẹ̀ fúnraraa rẹ̀. Kí ni ò ń ṣe?
Mò ń fọ eyínìn mi fúnraraà mi.

1. Tádé/ wẹ̀ ara.
2. Ọ̀gbẹ́ni Adé/ fọ aṣọ.
3. Kẹ́mi àti Títí /ya irun.
4. Ìwọ/ nu ara (conversational context).
5. Èmi/ pa ara.
6. Omidan Òdúṣọlá/ fọ ọwọ́.
7. Ọ̀jọ̀gbọ́n Owólabí/ ka ìwé.
8. Ìwọ àti Títí/ jẹ oúnjẹ (conversational context).
9. Ìwọ àti Títí/ jẹ oúnjẹ (non-conversational context).
10. Tósìn/ se oúnjẹ.

 CC – 2011 The University of Texas at Austin

Expressions such as ojoojúmọ́, ọ̀sọ̀ọ̀sán, alaalẹ́, ọdọọdún etc. indicate what one does every time.

For example, **ọdún** means **year**. However, **ọdọọdún** implies **every year**.

| | | | | |
|---|---|---|---|---|
| ojúmọ́ | (day) | → | ojoojúmọ́ | (every day) |
| àárọ̀ | (morning) | → | àràárọ̀ | (every morning) |
| ọ̀sán | (afternoon) | → | ọ̀sọ̀ọ̀sán | (every afternoon) |
| alẹ́ | (night) | → | alaalẹ́ | (every evening) |
| oṣù | (month) | → | oṣoooṣù | (every month) |
| ọ̀sẹ̀ | (week) | → | ọ̀sọ̀ọ̀sẹ̀ | (every week) |
| ọdún | (year) | → | ọdọọdún | (every year) |

## Iṣẹ́ Ṣíṣe 4

Ó kàn ẹ́. Sọ fún wa àwọn nǹkan tí o máa ń ṣe lójoojúmọ́.
*It's now your turn. Tell us what you do everyday.*

**Bí àpẹẹrẹ:**

Láràárọ̀ tí mo bá jí, mo máa ń wẹ̀. Lẹ́yìn náà, mo máa ń fọ eyínìn mi. Lẹ́yìn tí mo bá fọ eyínìn mi tán, mo máa ń……….. lọ̀sọ̀ọ̀sán, mo máa ń………..

## Iṣẹ́ Ṣíṣe 5

Fi ọ̀rọ̀ tí ó bá yẹ dí àwọn àlàfo yìí
*Fill in the spaces with appropriate words.*

_____________ tí mo bá jí ni mo máa ń wẹ̀. Ṣùgbọ́n ní _____________ n kò lè ṣaláì má jẹ oúnjẹ ọ̀sán. Kì í ṣe pé mo fẹ́ràn oúnjẹ púpọ̀ àmọ́, n kì í fi oúnjẹ alẹ́ẹ̀ mi ṣeré ní _____________. Fún aṣọ ọ̀sẹ̀ kan, _____________ ni mo máa ń fọ àwọn aṣọ̀ọ̀ mi nítorí pé n kò ní ààyè láàrin ọ̀sẹ̀, ṣùgbọ́n _____________ ni mo máa ń ra aṣọ tunun fún ilé-ìwée mi.

 CC – 2011 The University of Texas at Austin

## Cultural Vignette: Ìmọ́tótó

Àwọn Yorùbá jẹ́ afínjú ènìyàn. Wọ́n kórìrá ìdọ̀tí ganan ni. Wọ́n gbàgbọ́ pé bí ènìyàn kò tilẹ̀ lówó lọ́wọ́ láti fi ra oríṣiríṣi àṣọ ìgbàlódé, ìwọ̀nba nǹkan tí ènìyàn bá ní, kí ènìyàn ṣe ìtọ́jú rẹ̀ kí ó mọ́ tónítóní. Wọ́n gbàgbọ́ pé kí ènìyàn jí ní òwúrọ̀ kí ó fọ eyínin rẹ kí ó dá ṣáká, kí ó gé èékánná rẹ̀, kí ó wẹ̀, kí ó tọ́jú irunun rẹ̀, kí ó sì wọ asọ tí ó mọ́ kí ó tó dábàá láti pé pẹ̀lú àwọn ènìyàn láwùjọ. Ìdí nìyí tí wọ́n fi máa ń pa á lówe pé 'Wọ̀mbọ̀ wọmbọ kọ́ leyín, béyín bá ṣe méjì kí ó ṣá à funfun'. Èyí túmọ̀ sí pé ìmọ́tótó se pàtàkì fún ọmọlúwàbí. Àwọn Yorùbá gbàgbọ́ pé tí ènìyàn bá jẹ́ onímọ̀ọ́tótó nípa títọ́jú araa wọn, àìsàn àti àárùn yóò jìnnà réré sí sàkání onítọ̀hún. Wọ́n tún ní ìgbàgbọ́ pé ìmọ́tótó ń ṣokùnfà ìlera tó péye. Wọ́n á ní ẹni tó ní ìlera ló lóhun gbogbo. Fún àwọn Yorùbá, ìlera lọrọ̀ fún ohun gbogbo. Àwọn Yorùbá máa ń kọ oríṣiríṣi orin nípa ìmọ́tótó láti kọ́ àwọn ọmọọ wọ́n ní ìṣe pàtàkì ìmọ́tótó. Bí àpẹẹrẹ:

---

'Ìmọ́tótó ló lè ṣẹ́gun àrùn gbogbo (2x)
Ìmọ́tótó ilé, ìmọ́tótó ara, ìmọ́tótó oúnjẹ
Ìmọ́tótó ló lè ṣẹ́gun àrùn gbogbo'.

àti

---

'Wẹ̀ kí o mọ́
Gé èékánná rẹ
Jẹun tó dára lásìkò
Má jẹun jù'.

Nítorí àwọn orísì ẹ̀kọ́ pàtàkì báyìí, àwọn ọmọdé mọ̀ pé tí wọ́n bá jí ní ọ̀wúrọ̀, balùwẹ̀ ni ibi àkọ́kọ́ tí wọ́n gbọ́dọ̀ lọ láti lọ tọ́ju araa wọn kí wọ́n tó ṣe ohunkóhun. Ìmọ́tótó ṣe pàtàkì fún ẹ̀dá ènìyàn.

 CC – 2011 The University of Texas at Austin

### Iṣẹ́ Ṣíṣe 6

Dáhùn àwọn ìbéèrè wọ̀nyí ní ẹ̀kúnrẹ́rẹ́.
*Answer the following questions in complete sentences.*

1. Kí ni ìdí tí àwọn Yorùbá fi kórira ìdọ̀tí?
2. Irú ènìyàn wo ni àwọn Yorùbá jẹ́?
3. Kí ni ìrètí àwọn Yorùbá pé kí ènìyàn kọ́kọ́ ṣe ní òwúrọ̀ tí ó bá jí?
4. Àǹfààní wo ní ìmọ́tótó ń ṣe fún àwọn ènìyàn?
5. Kí ni pàtàkì ẹ̀kọ́ nípa ìmọ́tótó fún àwọn ọmọdé ní ilẹ̀ẹ Yorùbá? Kí ni èrò rẹ nípa orin yìí “Wẹ̀ kí o mọ́…?

### Iṣẹ́ Ṣíṣe 7

Kọ ìtumọ̀ àwọn ọ̀rọ̀ wọ̀nyí sílẹ̀ ní èdèe Yorùbá.
*Write down the meanings of these words in Yorùbá.*

1. ìmọ́tótó
2. kórira
3. ìlera lọrọ̀
4. àṣọ ìgbàlódé

### Iṣẹ́ Ṣíṣe 8

Kọ ewì kan ní èdèe Yorùbá tí ó jẹ mọ́ ìmọ́tótó ní ìlúu rẹ
*Write a poem about cleanliness in your country.*

### Iṣẹ́ Ṣíṣe 9

Sọ '**bẹ́ẹ̀ ni**' tàbí '**bẹ́ẹ̀ kọ́**' fún àwọn gbólóhùn wọ̀nyí.
*State whether the following sentences are true or false.*

| | BẸ́Ẹ̀ NI | BẸ́Ẹ̀ KỌ́ |
|---|---|---|
| 1. Àwọn Yorùbá fẹ́ràn ìdọ̀tí. | ☐ | ☐ |
| 2. Àwọn Yorùbá kò ní ìgbàgbọ́ nínú eyín funfun. | ☐ | ☐ |
| 3. Òtítọ́ ni pé ìlera ni ọrọ̀. | ☐ | ☐ |
| 4. Orin kíkọ kì í ṣe ọ̀nà kan láti kọ́ àwọn ọmọ ní ẹ̀kọ́. | ☐ | ☐ |
| **5.** Tí àwọn Yorùbá bá ti jí, oúnjẹ ni wọ́n kọ́kọ́ máa ń jẹ. | ☐ | ☐ |

 CC – 2011 The University of Texas at Austin

## Iṣẹ́ Ṣíṣe 10

So àwọn tí ó bara mu ni ọ̀wọ́ A àti ọ̀wọ́ B papọ̀.
*Match the words in column A with those in column B.*

| A | B |
|---|---|
| Ìmọ́tótó | belief |
| ìdọ̀tí | health |
| ìlera | illness |
| ìgbàgbọ́ | cleanliness |
| àrùn | dirt |

## Vowel Assimilation

This is a phonological process by which one vowel assimilates into the other when they are contiguous.

In A below, the process by which the first vowel (V1) assimilates into the next vowel (V2), or the second vowel (V2) in C assimilates into the first vowel (V1) is known as vowel assimilation.

| A | | | B | |
|---|---|---|---|---|
| <u>V1</u> | <u>V2</u> | | | |
| kú | ilé | → | kúulé | *a greeting to welcome someone into the house* |
| kú | ìrọ̀lẹ́ | → | kúùrọ̀lẹ́ | *good (early) evening* |

| C | | | D | |
|---|---|---|---|---|
| <u>V1</u> | <u>V2</u> | | | |
| kú | àárọ̀ | → | káàárọ̀ | *good morning* |
| Ojú | irin | → | ojúurin | *railroad* |
| Ọjà | Ọba | → | Ọjàaba | *the name of a market in Ìbàdàn city, Nigeria* |

Assimilation can be either progressive
V1 + V2 → V1V1 in which case kú + ilé → kúuié,
or regressive
V1+V2 → V2V2 as in kú + alẹ́ → káalẹ́.

 CC – 2011 The University of Texas at Austin

## Vowel Lengthening

Vowel lengthening occurs when a vowel is duplicated vowel. The assimilation of one vowel by another vowel across word boundaries results in vowel lengthening as in most of B and D above.

Vowel lengthening occurs at vowel + consonant word boundaries in a possessive relationship such as ilée bàbá (*bàbá's house*). However, vowel lengthening is unnecessary when it is V+V as in ilé ìyá (*ìyá's house*), which means that vowel lengthening does not necessarily occur because of contiguity of vowels. Examples of vowel lengthening are found in F below wherethe final vowels of **ilé** and **ajá** become lengthened.

## The partitive ti

The genitival particle 'ti' occurs before a noun or a pronoun as in the following examples:

| E | | F | |
|---|---|---|---|
| Ilé ti ọ̀rẹ́ | → | ìlée tọ̀rẹ́ | *friend's house* |
| Ajá ti àwa | → | ajáa tiwa | *our dog* |

The final vowel in **Ìlé** and **ajá** before the partitive becomes lengthened in column F above.

Vowel lengthening also occurs when a vowel is duplicated as in the following examples of third person singular object pronouns following their verbs:

| | |
|---|---|
| mo rí i | *I saw it* |
| ó jẹ ẹ́ | *s/he ate it* |
| ó tú u | *s/he untied it* |
| Adé bó o | *Adé peeled it* |

## Vowel Deletion/Vowel Contraction

Vowel deletion is a product of vowel contraction. Vowel deletion is a step in the phonological process of vowel contraction not assimilation. Assimilation and contraction are two different phonological processes. In the case of vowel contraction, when two vowels are in contiguous relationship across word boundaries, one of them is deleted and the two words contract to become one.

| | | | |
|---|---|---|---|
| ti ọ̀rẹ́ | → | tọ̀rẹ́ | *that of a friend(a friend's)* |
| ti àwa | → | tàwa | *that of ours(ours*) |

| | | | |
|---|---|---|---|
| rí ẹja | → | rẹ́ja | *to see fish* |
| ta iṣu | → | taṣu | *to sell yam(s)* |
| ra ẹran | → | rẹran | *to buy meat* |

Vowel deletion can occur without contraction when it is not across word boundaries as in the following examples:
Adéọlá → Déọlá
Ọládépò → Ládépò

## Iṣẹ́ Ṣíṣe 11

Vowel lengthening (VL) or vowel contraction (VC)? Write out the complete words.

**Bí àpẹẹrẹ:**

Kun ojú → kunjú (VC)

1. pa ara → _
2. bọ́ ojú →__
3. se ẹja → _
4. kú ìrọ̀lẹ́ → ____
5. ilé ijó →__
6. ọmọ iṣẹ́ → ____
7. gé igi →__
8. fọ ẹnu →__
9. wọ aṣọ → ____
10. gun igi→__

 CC – 2011 The University of Texas at Austin

# Lesson 3 - Ẹ̀kọ́ Kẹta: Our House

## ILÉ ALÁMỌ̀ ÀTI ILÉE SÌMẸ́ǸTÌ

Ní ilẹ̀ẹ Yorùbá, orísị ilé méjì ni ó wà: ilé alámọ̀ àti ilé oní sìmẹ́ǹtì. Ilé alámọ̀ jẹ́ ilé tí ó wà kí aláyé tó dáyé. Àwọn òyìnbó aláwọ̀ funfun ni wọ́n gbé ilée búlọ́ọ̀kù wá. Ilé alámọ̀ wọ́pọ̀ ní oko àti ilú kékeré. Ilée símẹ́ǹtì ni ènìyàn sáábà máa ń rí tí ènìyàn bá lọ sí àwọn ìlú ńlá bíi Èkó àti Ìbàdàn. Erùpẹ̀ amọ̀ pupa àti omi ni wọ́n pò pọ̀ láti fi kọ́ ilé alámọ̀. Mọlémọlé ni orúkọ àwọn tí ó mọ̀ nípa bí wọ́n ṣe ń kọ́ ilé alámọ̀. Púpọ̀ nínú ilé alámọ̀ ni wọ́n máa ń ní fèrèsé tí wọ́n ń pè ní 'máràṣáná'. Fèrèsé náà máa ń kéré ganan ni. Púpọ̀ nínú ilé alámọ̀ ni wọn kì í ní ilé ìgbọ̀nsẹ̀. Nítorí ìdí èyí ni àwọn alákọ̀wé kì í fi í gbé ibẹ̀.

Àwọn òyìnbó aláwọ̀ funfun ni wọ́n mú àṣàa kíkọ́ ilée sìmẹ́ǹtì wá. Sìmẹ́ǹtì àti iyanrìn ni wọ́n sì máa ń lo láti fi kọ́ ilée sìmẹ́ǹtì. Ilé tí wọ́n fi sìmẹ́ǹtì kọ́ máa ń ní agbára ju ilé alámọ̀ lọ nítorí pé sìmẹ́ǹtì àti iyanrìn ní agbára láti mú ilé dúró. Ilée sìmẹ́ǹtì wọ́pọ̀ ní àwọn ilú ńlá bíi Òṣogbo, Ìbàdàn, Èkó, Ilé-Ifẹ̀ àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Ilé alámọ̀ kì í sáábà ní àjà nítorí pé kò ní agbára bí ilée sìmẹ́ǹtì.

### Iṣẹ́ Ṣíṣe 1

Dáhùn àwọn ìbéèrè wọ̀nyí ní ẹ̀kúnrẹ́rẹ́.
*Answer the following questions in complete sentences.*

1. Orísị ilé mélòó ni ó wà ní ilẹ̀ẹ Yorùbá?
2. Dárúkọ àwọn ilé náà.
3. Níbo ni ilé alámọ̀ wọ́pọ̀ sí?
4. Báwo ni ilé tí wọ́n fi sìmẹ́ǹtì kọ́ ṣe dé ilẹ̀ẹ Yorùbá?
5. Àwọn ohun-èlò wo ni a nílò láti fi kọ́ ilé alámọ̀?
6. Kí ni ìdí rẹ̀ tí àwọn alákọ̀wé kì í fí gbé ilé alámọ̀?
7. Kí ni orúkọ tí àwọn ènìyàn máa ń pe àwọn tí wọ́n ń kọ́ ilé?
8. Kí ni àwọn ohun-èlò tí wọ́n máa ń lò fún ilée sìmẹ́ǹtì?
9. Sọ ìdí rẹ̀ tí wọ́n fi máa ń fi sìmẹ́ǹtì àti iyanrìn kọ́ ilé lóde-òní.
10. Báwo ni àwọn fèrèsé ilé oní sìmẹ́ǹtì ṣe yàtọ̀ sí ti alámọ̀?

 CC – 2011 The University of Texas at Austin

## Iṣẹ́ Ṣíṣe 2

Mú èyí tó yẹ nínú àwọn wọ̀nyí sí ibi tó yẹ gẹ́gẹ́ bí o ṣe rí i kà nínú àyọkà òkè yìí.
*Check the appropriate category for the following expressions according to the text (***ILÉ ALÁMỌ̀ ÀTI ILÉE SÌMẸ́NTÌ)** *above.*

| | Ilé alámọ̀ | Ilée sìmẹ́ntì |
|---|---|---|
| 1. Yorùbá | ☐ | ☐ |
| 2. Àwọn òyìnbó | ☐ | ☐ |
| 3. Búlọ́ọ̀kù | ☐ | ☐ |
| 4. Oko àti ìlú kékeré | ☐ | ☐ |
| 5. Erùpẹ̀ amọ̀ pupa | ☐ | ☐ |
| 6. Mọlémọlé | ☐ | ☐ |
| 7. Iyanrìn | ☐ | ☐ |
| 8. Àjà | ☐ | ☐ |
| 9. Agbára | ☐ | ☐ |
| 10. Èkó àti Ìbàdàn | ☐ | ☐ |

## Iṣẹ́ Ṣíṣe 3

Kọ ìtumọ̀ àwọn ọ̀rọ̀ wọ̀nyí sílẹ̀ ní èdèe Yorùbá.
*Write down the meanings of these words in Yorùbá.*

1. búlọ́ọ̀kù
2. erùpẹ̀ amọ̀ pupa
3. mọlémọlé
4. iyanrìn
5. àjà

 CC – 2011 The University of Texas at Austin

## Iṣẹ́ Ṣíṣe 4

Sọ **bẹ́ẹ̀ ni** tàbí **bẹ́ẹ̀ kọ́** fún àwọn gbólóhùn wọ̀nyìí.
*State whether the following sentences are **true** or **false**.*

| | BẸ́Ẹ̀ NI | BẸ́Ẹ̀ KỌ́ |
|---|---|---|
| 1. Oríṣi ilé méjì ni ó wà: ilé alámọ̀ àti iléе pako. | ☐ | ☐ |
| 2. Ilé alámọ̀ wọ́pọ̀ ní ilú ńlá ńlá. | ☐ | ☐ |
| 3. Èrùpẹ̀ amọ̀ pupa àti omi ni wọ́n fi ń kọ́ ilée sìmẹ́ǹtì. | ☐ | ☐ |
| 4. Gbogbo ilé alámọ̀ lo ní ilé ìgbọ̀nsẹ̀ | ☐ | ☐ |
| 5. Ilé tí wọ́n fi sìmẹ́ǹtì kọ́ máa ń ní agbára ju ilé alámọ̀ lọ. | ☐ | ☐ |

## Iṣẹ́ Ṣíṣe 5

Parí àwọn gbólóhùn wọ̀nyí.
*Complete the following questions*.

1. Ilée ______________________________ wọ́pọ̀ láàrin àwọn Yorùbá.
2. Àwọn ______________________________ ni wọ́n gbé àṣà ilée sìmẹ́ẹ̀ǹtì wá.
3. Ilée ____________________ ní agbára ju ilée ______________________ lọ.
4. Àwọn ___________________fẹ́ràn láti máa gbé ilée ____________________.
5. ______________________ àti ___________________ni wọ́n fi ń kọ́ ilé alámọ̀.

### Cultural Vignette: Ilé Olókè

Oríṣiríṣi àjà ni àwọn ilé máa ń ní ní ilẹ̀ẹ Yorùbá. Púpọ̀ nínú àwọn ilé tí wọ́n wà ní oko àti ìgbèríko ni ó máa ń ní àjà kan. Àwọn ilé tí ó wà ní ìlú títóbi bíi Èkó, Ìbàdàn, Abẹ̀òkúta, Àkúrẹ́, Adó-Èkìtì àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ máa ń ní àjà méjì, mẹ́ta àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ.

Àwọn òyìnbó aláwọ̀ funfun ló mú àṣà ilé alájà méjì wà sí ilẹ̀ẹ Yorùbá. Gẹ́gẹ́ bíi àwọn akọ̀tàn ti sọ, ìlúu Bàdágírì ni wọ́n kọ́kọ́ kọ́ ilé olókè méjì sí. Ó lé lọ́gọ́rùnún ọdún sẹ́yìn tí wọ́n kọ́ ilé yìí. Àwọn òyìnbóo Míṣánnárì ni wọ́n kọ́ ilé alájà méjì náà. Ní ìlú Ìbàdàn, àdúgbòo Kúdẹtì ni wọ́n kọ́kọ́ kọ́ ilé olókè méjì sí. Ilé olókè jẹ́ ilé tí ó wọ́n láti kọ́. Àwọn ènìyàn pàtàkì ní àwùjọ ni wọ́n ní owó àti agbára láti kọ́ ilé olókè méjì ní ilẹ̀ẹ Yorùbá.

 CC – 2011 The University of Texas at Austin

## Iṣẹ́ Ṣíṣe 6

Dáhùn àwọn ìbéèrè wọ̀nyí ní ẹ̀kúnrẹ́rẹ́.
*Answer the following questions in complete sentences.*

1. Oríṣi àjà mélòó ni àwọn ilé máa ń ní ní ilẹ̀ẹ Yorùbá?
2. Àjà mélòó ni àwọn ilé tí ó wà ní ìlú títóbi bíi Èkó, Ìbàdàn, Abẹ̀òkúta, Àkúrẹ́, Adó-Èkìtì àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ máa ń ní?
3. Níbo ni wọ́n kọ́kọ́ kọ́ ilé olókè méjì sí?
4. Ìgbà wo ni wọ́n kọ́ ilé olókè méjì yìí?
5. Àwọn òyìnbó wo ni ó kọ́ ilé alájà méjì náà?

## Iṣẹ́ Ṣíṣe 7

Sọ **bẹ́ẹ̀ ni** tàbí **bẹ́ẹ̀ kọ́** fún àwọn gbólóhùn wọ̀nyí.
*State whether the following sentences are* ***true*** *or* ***false****.*

| | BẸ́Ẹ̀ NI | BẸ́Ẹ̀ KỌ́ |
|---|---|---|
| 1. Ilé alájà jẹ́ àṣà ìlú òkèèrè. | ☐ | ☐ |
| 2. Àwọn ilé tí ó wà ní ìlú kékeré máa ń ní àjà púpọ̀. | ☐ | ☐ |
| 3. Ìlú Èkó nìkan ni àṣà ilé alájà púpọ̀ wá. | ☐ | ☐ |
| 4. Àwọn Hausa ni wọ́n mú àṣà ilé alájà kíkọ́ wa. | ☐ | ☐ |
| 5. Ìlú Ẹ̀pẹ́ ni wọ́n kọ́kọ́ kọ́ ilé olókè méjì sí. | ☐ | ☐ |
| 6. Àwọn òyìnbó Kọ̀ríà ni wọ́n kọ́ ọ. | ☐ | ☐ |
| 7. Ó ti tó ọgọ́rùnún ọdún tí wọ́n kọ́ ilé olókè ní ilẹ̀ẹ Yorùbá. | ☐ | ☐ |
| 8. Àwọn òyìnbó míṣánnárí ni wọ́n kọ́ ilé alájà méjì náà. | ☐ | ☐ |
| 9. Ilé olókè jẹ́ ilé tí kò wọ́n láti kọ́. | ☐ | ☐ |
| 10. Àwọn gbajúmọ̀ láwùjọ nìkan ni wọ́n lè kọ́ ilé alájà púpọ̀. | ☐ | ☐ |

 CC – 2011 The University of Texas at Austin

## Iṣẹ́ Ṣíṣe 8

Wá àwọn ọ̀rọ̀ wọ̀nyí.

*Look for these words in the puzzle below. Pay attention to the tones!*

**ààfin, afínjú, àjà, alákọ̀wé, ayálégbé, ehoro, fèrèsé, góòlù, ibùsùn, ìdọ̀tí**

| | | | | | | | | | | | | | | |
|---|---|---|---|---|---|---|---|---|---|---|---|---|---|---|
| à | à | f | i | n | a | g | b | a | f | i | n | j | u | j |
| i | g | b | a | ń | l | a | d | f | g | i | a | d | e | a |
| a | g | ó | ò | l | ù | a | d | a | è | a | i | g | o | g |
| y | l | í | ọ̀ | à | i | o | l | ọ̀ | y | r | y | a | l | u |
| á | è | á | ì | p | j | g | n | á | g | a | è | a | k | d |
| l | á | k | k | ì | ọ̀ | à | ì | í | k | b | l | s | b | i |
| é | l | j | u | ọ̀ | d | l | á | b | b | ọ̀ | ọ̀ | e | é | u |
| g | d | è | á | h | w | ọ̀ | e | l | ù | e | w | n | g | í |
| b | ọ̀ | a | d | o | o | é | t | h | á | s | Í | a | m | b |
| é | s | e | a | r | è | r | á | í | o | w | ù | y | j | u |
| d | a | g | o | o | l | u | ì | b | d | r | á | n | a | à |
| a | l | a | w | a | d | l | l | d | a | e | o | d | i | w |
| i | f | l | b | u | s | u | n | o | ọ̀ | l | d | i | e | y |
| f | è | r | è | s | e | g | o | o | d | t | e | e | d | í |
| a | f | í | n | j | ú | á | y | a | l | à | a | f | i | n |

## Iṣẹ́ Ṣíṣe 9

Kọ ìtumọ̀ àwọn ọ̀rọ̀ wọ̀nyí sílẹ̀ ní èdè Yorùbá.

*Write down the meanings of these words in Yorùbá.*

1. ìgbèríko
2. àṣà
3. akọ̀tàn
4. òyìnbóo Míṣánnárì
5. ènìyàn pàtàkì

 CC – 2011 The University of Texas at Austin

## Ọ̀rọ̀ àdáṣọ *(Monologue)*

### Fúláàtì àbúròo màmáà mí ọkùnrin

Ní ilẹ̀ẹ Nàìjíríà, àpátímẹ́ẹ̀ǹtì ni àwọn Yorùbá máa ń pè ní fúláàtì. Tí àwọn ènìyàn kò bá tí ì ṣetán láti kọ́ ilé, wọ́n máa ń rẹ́ǹtì àpátímẹ́ẹ̀ǹtì láti gbé. Àwọn alákọ̀wé ni wọ́n sáábà máa ń gbé fúláàtì.

Àbúrò màmáà mi jẹ agbẹjọ́rò ní ìlú Ìbàdàn. Wọ́n sì rẹ́ǹti fúláàtì kan sí Bódìjà Tuntun. Orúkọ wọn ni Lọya Adébímpé. Fúláàtì wọn tóbi ganan ni. Ó ní pálọ̀ ńlá méjì àti yàrá ìbùsùn mẹ́rin. Yàrá tí ó tòbi jù ni yàrá àbúrò màmáà mi àti ìyàwóo wọn. Yàrá yìí ní baluwẹ̀ àti ilé ìyàgbẹ́ tirẹ̀ lọ́tọ̀. Balùwẹ̀ àti ilé ìyàgbẹ́ kan tó kù wà fun àwọn ọmọ àti àwọn àlejò.

Ènìyàn kò lè ṣàdédé wọ fúláàtì àbúròo màmáà mi láì ṣe pé ó jẹ́ ẹni mímọ̀. Ìdí nìyí tí o fí jẹ́ pé ìta gbangba ni wọ́n ti máa ń gbàlejò. Tí ó bá ṣe ènìyàn mímọ̀ ni ó wá kí àwọn ìdílé àbúròo màmáà mi, pálọ̀ tí ó wà ní iwájú ni wọ́n máa jókòó sí láti bá wọn sọ̀rọ̀ àti ṣeré. Ṣùgbọ́n tí ó bá ṣe àlejò pàtàkì ni, pálọ̀ ńlá kejì ní wọ́n máa ti ń gbàwọ́n lálejò. Pálọ̀ ńlá yìí tóbi bíi ààfin Ọba. Wọ́n sí tún ṣe é lọ́ṣọ̀ọ́ lóríṣiríṣi pẹ̀lú àwọn ohun mèremère bí i góólù. Kódà kò yàtọ̀ sí ààfin. Ìdí nìyí tó fi jẹ́ pé àwọn àlejò pàtàkì nìkan ni wọ́n máa ń gbà láàyè láti jókòó níbẹ̀.

Ọmọ méjì péré ni àbúròo màmáà mi bí – Adébọ́lá àtí Adébóyè. Ọkùnrin àti obìnrin ni wọ́n. Adébọ́lá ń lo yàrá kan. Adébóyè náà sì ní yàrá tirẹ̀. Yàrá kan tókù ni yàrá àlejò. Fúláàtì àbúrò màmáà mi tóbi gan-an ni. Ọ̀pọ̀lọpọ̀ ènìyàn ni wọ́n máa ń sọ pé ó wu àwọn. Ìta gbangbaa wọ́n tẹ́jú, ó sì láàyè tó pọ̀. Ohun tó wù mí jùlọ nípa fúláàtì àbúrò màmáa mi nipé wọ́n fi ọgbà yiká tó fi jẹ́pé àwọn ènìyàn tí wọ́n ń lọ níta kò le rí ohun tí ó ń lọ nínúu fúláàtì àbúrò màmáà mi.

 CC – 2011 The University of Texas at Austin

## Iṣẹ́ Ṣíṣe 10

Dáhùn àwọn ìbèérè wọ̀nyí ní ẹ̀kúnrẹ́rẹ́.
*Answer the following questions in complete sentences.*

1. Ta ni wọ́n ń sọ̀rọ̀ nípa fúláàtì rẹ̀ nínú nǹkan tí a kà?
2. Irú iṣẹ́ wo ni wọ́n ń ṣe?
3. Níbo ni fúláàtì tí a sọ̀rọ̀ rẹ̀ wà ní ìlú Ìbàdàn?
4. Báwo ni a ṣe ṣe àpèjúwe fúláàtì náà?
5. Ta ni ó ń lo yàrá tí ó tóbi jù nínúu fúláàtì yìí?
6. Kí ni o rò pé ó jẹ́ ìdí rẹ̀ tí Lọya Adébímpé kì í fí gba àwọn ènìyàn láàyè láti wọlé láì ṣe pé wọ́n jẹ́ ẹni mímọ̀?
7. Irú àwọn ènìyàn wo ni wọ́n le wọ pálọ̀ ńlá kejì? Kí ni ìdí èyí?
8. Ọmọ mélòó ni Lọya Adébímpé bí? Kí ni orúkọọ wọn?
9. Yàrá mélòó ni wọ́n ń lò?
10. Kí ni ẹni tí ó ń sọ̀rọ̀ nípa Lọya Adébímpé fẹ́ràn jùlọ nípa fúláàtì yìí? Báwo ni ẹni náà ṣe jẹ́ sí Lọya Adébímpé?

## Iṣẹ́ Ṣíṣe 11

Sọ **bẹ́ẹ̀ ni** tàbí **bẹ́ẹ̀ kọ́** fún àwọn gbólóhùn wọ̀nyí.
*State whether the following sentences are **true** or **false**.*

| | BẸ́Ẹ̀ NI | BẸ́Ẹ̀ KỌ́ |
|---|---|---|
| 1. Àpátíméẹ̀ǹtì ni àwọn Yorùbá máa ń pè ní fúláàtì | ☐ | ☐ |
| 2. Ẹ̀gbọ́nọn màmáà mi jẹ́ agbẹjọ́rò ní ìlú Ìbàdàn. | ☐ | ☐ |
| 3. Pálọ̀ ńlá méjì àti yàrá ìbùsùn mẹ́ta ni ó wà ní fúláàtì àbúrò màmáà mi | ☐ | ☐ |
| 4. Ènìyàn lè ṣàdédé wọ fúláàtì àbúròo màmáà mi. | ☐ | ☐ |
| 5. Ọmọ kan péré ni àbúròo màmáà mi bí | ☐ | ☐ |

## Iṣẹ́ Ṣíṣe 12

Parí àwọn gbólóhùn wọ̀nyí.
*Complete the following sentences.*

1. Àwọn ___________ ni wọ́n máa ń gbé àpátímẹ́ẹ̀ǹtì.
   a. alákọ̀wèé
   b. àgbẹ̀
   c. ọdẹ
   d. àgbàlagbà

2. _______________ ni àwọn Yorùbá máa ń pè ní fúláàtì.
   a. Ilé olókè
   b. Ilé onílẹ̀
   c. Àpátímẹ́ẹ̀ǹtì
   d. Fúláàtì

3. Iṣẹ́ _____________ni àbúrò Màmáà mi ń ṣe.
   a. alákọ̀wèé
   b. àgbẹ̀
   c. ọdẹ
   d. agbẹjọ́rò

4. Àbúròo màmáà mi ń gbé ní àdúgbòo ______________?
   a. Mọ́kọ́lá
   b. Bẹẹrẹ
   c. Bódìjà Tuntun
   d. Bódìjà Àtijọ́

5. Ọmọ ___________ ni àbúròo màmáà mi bí?
   a. mẹ́fà
   b. méjì
   c. mẹ́rin
   d. márùnún

 CC – 2011 The University of Texas at Austin

# Lesson 4 - Ẹ̀kọ́ Kẹrin

## Our House



### Ọ̀rọ̀ àdáṣọ *(Monologue)*

**Ilée wa (*Our house)***

Ilée wa jẹ́ ilé alájà méjì. Ọ̀pọ̀lọpọ̀ ojúlé ni ilé yìí ní. Àjà kìíní ní yàrá méjọ, bẹ́ẹ̀ sì ni àjà kejì ní yàrá méjọ pẹ̀lú. Bàbáà mi fi gbogbo yàrá méjẹ̀ẹ̀jọ tí ó wà ní àjà kìíní rẹ́ǹtì fún àwọn ayálégbé. Àwọn ìdílé mẹ́rin ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀ ni wọ́n gba àjà kìíní ní yàrá méjì–méjì. Wọ́n fi yàrá kan ṣe yàrá ìbùsùnun wọn. Ilé ìdáná méjì, balúwẹ̀ méjì àti ilé ìyàgbẹ́ méjì ni ó wa ní àjà kìíní. Àwọn ayalégbé sì pín wọn ní ìdílé méjì sí balúwẹ̀, ilée ìdáná àtí ilée ìyàgbẹ́ kọ̀ọ̀kan.

Yàrá mẹ́jọ ni ó wà ní àjà kejì ṣùgbọ́n èmi àti àwọn òbí mi pẹ̀lú awọn ẹ̀gbọ́n àti àbúròò mí nìkan ni à ń gbé ní àjà kejì. A ní pálọ̀ ńlá kan tí a ti máa ń gba àlejò. A sì tún ní pálọ̀ kékeré tí awa ọmọ ti máa ń ṣeré, tí a sì ti máa ń wo tẹlifíṣàn. Bàbáà mi ní yàràa ti wọn tí ó ti pálọ̀ ńlá. Yàrá ìyáà mi sì tẹ̀lé ti bàbáà mi. Ẹ̀gbọ́nọ̀n mi ọkùnrin tí ó wà ní Yunifásítì ti Ọbáfẹ́mi Awólọ́wọ̀ ní Ilé-Ifẹ̀ ní yàrá tiwọn lọ́tọ̀, ó sì súnmọ́ pálọ̀ ti àwa yòókù.

Yàrá àwọn ọmọ ọkùnrin méjì yòókù àti ti awa obìnrin wà ní ìkangun ilé. Yàrá ìyáàgbà ni ó tẹ̀lé ti ìyáa mi. Gbogbo yàrá tí ó wà ní àjà kejì ni àwọn ẹbíi mi ń gbé tó bẹ́ẹ̀ gẹ́ tí ó fi jẹ́ wípé kò sí àyè fún ayálégbé kankan láti gbé pẹ̀lúu wa. Yàrá ìdáná méjì, balúwẹ̀ méjì àtì ilé ìyàgbẹ́ méjì ni ó wà ní àjà kejì bí ó ti wà ní àjà kìíní. Ṣùgbọ́n àwọn ẹbí mi nìkan ni wọn ń lo gbogbo àwọn yàrá wọ̀nyí. Eléyìí fún wa láàyè púpọ̀ láti rí ibi kó ẹrù sí. Kódà ìyáa mi ráàyè sin nǹkan ọ̀sìnin wọn bíi adìẹ, ehoro àti tòlótòló. Bàbáà mi fi ọgbà yí ilée wa ká. Eléyìí sì fún àwa ọmọdé láńfààní láti ṣere sí ibi tí ó bá wùwá nínú ọgbàa wa. Ọgbà ilée wa tóbi gan-an ni, ó sì tẹ́jú púpọ̀.

 CC – 2011 The University of Texas at Austin

## Iṣẹ́ Ṣíṣe 1

Dáhùn àwọn ìbéèrè wọ̀nyí.
*Answer the following questions in complete sentences.*

1. Àjà mélòó ni ilé tí a ká nípa rẹ̀ ní?
2. Àwọn ayálégbé mélòó ni wọ́n ń gbé ilé yìí?
3. Pálọ̀ mélòó ni ayálégbé kọ̀ọ̀kan ní?
4. Yàrá mélòó ni ó wà ní gbogbo àwọn àjà tí ilé náà ní?
5. Pálọ̀ mélòó ni àwọn onílé ní?
6. Níbo ni yàrá ìyáàgbà wà?
7. Balùwẹ̀ mélòó ni gbogbo àwọn ayálégbé ń lò?
8. Kí ló dé tí àwọn ayálégbé kankan kò fi le gbé pẹ̀lú àwọn onílé ní àjà ti wọn?
9. Kí ló dé tí àwọn ọmọdé fi le ṣeré sí ibi ti ó wù wọ́n ní ilé yìí?
10. Kí ni ìdí tí àyè fi gba ìyá láti sin nǹkan ọ̀sìn? Dárúkọ àwọn ǹnkan ọ̀sìn yìí.

## Iṣẹ́ Ṣíṣe 2

Parí àwọn gbólóhùn wọ̀nyí.
*Complete the following questions.*

Ilée wa jẹ́ ilé alájà ____________. Àwọn ayálégbé ____________ ni wọn wà ní ilée wa. Gbogbo àpapọ̀ yàráa tí ò wà ní ilée wá jẹ́ ____________. ____________ mi ọkùnrin tí ó wà ní Yunifásítì ti Ọbáfẹ́mi Awólọ́wọ̀ ní Ilé-Ifẹ̀ ní yàráa tiwọn lọ́tọ̀ nítorí pé a ní yàrá tí ò pọ̀. Kódà, màmáa mi ní àǹfààní láti sin àwọn nǹkan ọ̀sìn wọn bí i ____________, ____________ àti ____________.

## Iṣẹ́ Ṣíṣe 3

Kọ ìtumọ̀ àwọn ọ̀rọ̀ wọ̀nyí sílẹ̀ ní èdèe Yorùbá.
*Write down the meanings of these words in Yorùbá.*

1. ayálégbé
2. nǹkan ọ̀sìn
3. yàrá ìdáná
4. ilé ìyàgbẹ́
5. ìkangun ilé

## Iṣẹ́ Ṣíṣe 4

Ó kàn ẹ́. Sọ fún wa nípa iléè bàbáà rẹ.

 CC – 2011 The University of Texas at Austin

## Iṣẹ́ Ṣíṣe 5

Ní méjì-méjì, ẹ sọ fùn araa yín nípa ibi tí ẹ̀ ń gbé.
*In pairs, tell your friend about where you live (your dorm, apartment etc)*

## Ọ̀rọ̀ àdáṣọ (*Monologue*)

**Tósìn ń sọ̀rọ̀ nípa yàráa rẹ̀**

Nínúu yàráà mi, mo ní ibùsùn, ìrọ̀rí, àga, tábìlì ìkàwé, kọ̀bọ́ọ̀dù ìkáṣọsí, rédíò alágbèéká kékeré kan, kápẹ́ẹ̀ti (ẹní àtẹ́ẹ̀ká) àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ.
Ní pálọ̀, àga onítìmùtìmù mẹ́rin ni wọ́n wà níbẹ̀, tẹlifíṣàn ńlá kan, rédíò ńlá kan, aago ńlá kan àti oríṣiríṣi àwòrán ara ògiri ni ó wa níbẹ̀ pẹ̀lú. Sítóòfù onígáàsì àti sítóòfù onikẹrosîînì wà nínúu ilé ìdáná. Bẹ́ẹ̀ náà sì ni fìrîìjì àti sîìnkì. Ohún-èlò ìdáná oríṣiríṣi bíi àwo, abọ́, ìkòkò, ṣíbí, fọ́ọ̀kì àti ọ̀bẹ náà sì wà níbẹ̀. Ẹ̀rọ omi, tọ́ọ̀bù, ṣáwà, sîìnkì, ọṣẹ ìwẹ̀ àti táwẹ̀ẹ̀lì wà nínúu balùwẹ̀.

## Iṣẹ́ Ṣíṣe 6

Dáhùn àwọn ìbèérè wọ̀nyí.
*Answer the following questions.*

1. Kí ni ó wà nínúu yàráaTósìn tí ó lè lò láti fi sùn?
2. Kí ni ó wà nínúu yàráaTósìn tí ó lè káṣọ sí?
3. Dárúkọ àwọn nǹkan tí ó wà nínúu pálọ̀ọ Tósìn?
4. Dárúkọ àwọn nǹkan tí ó wà nínú ilé ìdánáa Tósìn?
5. Níbo ni ó fẹ́ràn jù nípa ibi tí Tósìn ń gbé?

## Iṣẹ́ Ṣíṣe 7

Sọ **bẹ́ẹ̀ ni** tàbí **bẹ́ẹ̀ kọ́** fún àwọn gbólóhùn wọ̀nyí.
*State whether the following sentences are* ***true*** *or* ***false.***

| | BẸ́Ẹ̀ NI | BẸ́Ẹ̀ KỌ́ |
|---|---|---|
| 1. Àwọn nǹkan tí wọ́n ṣe pàtàkì wà ní yàráaTósìn. | ☐ | ☐ |
| 2. Tósìn máa ní àǹfààní láti mọ ohun tó ń lọ láwùjọ. | ☐ | ☐ |
| 3. Tósìn máa ní àǹfààní láti dáná ní ìgbàkúùgbà tí ó bá wù ú. | ☐ | ☐ |
| 4. YàráaTósìn dára láti gbé. | ☐ | ☐ |
| 5. Tósìn kò ní láti lọ pọn omi ni ibòmíràn kí ó tó lè wẹ̀. | ☐ | ☐ |

### Iṣẹ́ Ṣíṣe 8
Ó kàn ẹ́. Ṣe àpèjúwe yàráà rẹ.
*Now it's your turn. Describe your room.*



### Ọ̀rọ̀ àdásọ *(Monologue)*

Jídé ń sọ̀rọ̀ nípa ilé-ìwẹ̀ẹ rẹ̀.
(*Jídé is talking about his bathroom.)*

#### ILÉ-ÌWẸ̀Ẹ MI (MY BATHROOM)

Nínú ilé-ìwẹ̀ẹ mi, oríṣiríṣi nǹkan ni mo ní níbẹ̀ bíi ìpara, ìparun, ìyarun, ọṣẹ ìfọyín, ọṣẹ ìwẹ̀, ọṣẹ ìfọwọ́, aṣọ ìnura, omi tútù, omi gbígbóná, búrọ́ọ̀ṣì, kábínẹ́ẹ̀tì, kànhìnkànhìn, tíṣù, àti àwọn nǹkan mìíràn.

Ní gẹ́lẹ́ tí mo bá ti wọ inú ilé-ìwẹ̀ẹ mi, búrọ́ọ̀ṣì mi ni mo kọ́kọ́ máa ń kì mọ́lẹ̀ tí mà á fi ọṣẹ ìfọyín sí i. Mo bẹ̀rẹ̀ sí fọ ẹnu lọ nìyẹn. Lẹ́yìn ọ̀pọ̀lọ̀pọ̀ ìṣẹ́jú, mà á bu omi yálà tútú tàbí gbígbóná láti fi fọ ẹnuù mi mọ́.

Àwọn Yorùbá ní ìgbàgbọ́ pé omi tútú máa ń jẹ́ kí ara nà dáadáa, àmọ́ tí òtútù bá mú jù, omi gbígbóná ni mo máa ń fi í wẹ̀ pẹ̀lú ọṣẹ àti kànhìnkànhìn ní àárọ̀ kí gbogbo ìdọ̀tí ara le bá omi lọ. Mo máa fi ìpara àti ìparun ra ara àti irunùn mi. Tí mo bá ti wẹ̀ tán máa sì yarun pẹ̀lú. Lẹ́yìn gbogbo èyí, háà! Oúnjẹ yá láti jẹ nìyẹn!

### Iṣẹ́ Ṣíṣe 9
Dáhùn àwọn ìbéèrè wọ̀nyí.
*Answer the following questions.*

1. Kí ni Jídé máa ń kọ́kọ́ ṣe tí ó bá ti jí?
2. Ṣé ìwọ mọ̀ bọ́yá Jídé máa ń wẹ̀ tí ó bá ti jí? Kọ gbólóhùn kan jade láti inú àyọkà yìí láti fi gbe ìdáhùn rẹ lẹ́sẹ̀.
3. Ǹjẹ́ o rò pé Jídé ní ìmọ̀-tótó? Kí ni o fi dá ìwọ lójú?
4. Kí ni àwọn nǹkan tí ó ṣe pàtàkì tí o rò pé ó yẹ kí ó wà nínúu ilé-ìwẹ̀ẹ Jídé gẹ́gẹ́ bí o ṣe rí i kà nínúu ayọkà náà?
5. Ǹjẹ́ o rò pé Jídé fẹ́ràn oúnjẹ? Má ṣàì fi gbólóhùn kan gbe ìdáhùn rẹ lẹ́sẹ̀.

 CC – 2011 The University of Texas at Austin

## Iṣẹ́ Ṣíṣe 10

Dáhùn àwon ìbéèrè wọ̀nyí.
*Answer the following questions.*

**Bí àpẹẹrẹ:**

Kí ni a fi ń nura?

Aṣọ ínura tabí táwẹ̈ẹ̀li ni a fi ń nura

1. Kí ni a fi ń wẹ̀?
2. Kí ni a fi ń fọ ẹnu?
3. Kí ni a fi ń wo ojú?
4. Kí ni a fi ń ya irun?
5. Kí ni a fi ń fọ eyín?
6. Kí ni a fi ń nu ọwọ́
7. Kí ni àwọn ọkùnrin fi ń fá irùgbọ̀n
8. Kí ni a fi ń fọ irun?
9. Kí ni àwọn obìnrin fi ń kun ojú?
10. Kí ni a fi ń pa ara?

 CC – 2011 The University of Texas at Austin



# Chapter 11 - Orí Kọkànlá | NICE STYLE!

## *OBJECTIVES:*

In this chapter you will learn:

- About different types of clothing
- About seasonal clothings
- The use of the verbs fi_ lé / fi_ kọ́, wọ̀, dé/gẹ̀, wé, ró
- Further use of interrogatives
- Current trends in fashion

# Àwọn ọ̀rọ̀ (*Vocabulary*)

| Nouns | |
|---|---|
| àpọ́nlé | *respect* |
| àṣà | *culture* |
| aṣọ | *clothe* |
| bùbá | *a shirt or a blouse (Yorùbá style)* |
| búláòsì | *blouse (western style)* |
| èjìká | *shoulder* |
| fìlà | *hat* |
| gèlè | *a scarflike headgear* |
| gínnì | *guinea* |
| ìborùn | *shawl* |
| ìbọsẹ̀ | *sock(s)* |
| ìbọ̀wọ́ | *glove(s)* |
| ìgbéyàwó | *wedding* |
| ìmúra | *an outfit* |
| ìró | *a wrap-around cloth/ wrapper* |
| ìsìnkú | *funeral* |
| ìsọmọlórúkọ | *naming ceremony* |
| iyì | *honor* |
| jákẹ́ẹ̀tì | *jacket* |
| jíìnsì | *jeans* |
| kọjúsọ́kọ | *'to face one's husband'* |
| kóòtù | *coat* |
| obìnrin | *female* |
| oko | *farm* |
| ọjà | *market* |
| ọkùnrin | *male* |
| ọyẹ́ | *harmattan* |
| pàtàkì | *important* |
| ṣòkòtò | *a pair of pants* |
| súwẹ́tà | *sweater* |
| tíṣẹ̀ẹ̀tì | *t-shirt* |
| síkẹ́ẹ̀tì | *skirt* |
| yẹtí | *earring(s)* |

## Noun Phrases

| | |
|---|---|
| àsìkòo fọ́ọ̀lù | *fall season* |
| àkókò kọ̀ọ̀kan | *each season* |
| àsìkò mẹ́rin ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀ | *four different seasons* |
| aṣọ ẹ̀ẹ̀rùn | *clothes for the dry season* |
| aṣọ òde | *formal wear* |
| aṣọ ojoojúmọ́ | *informal clothing* |
| aṣọ òjò | *clothes for the rainy season* |
| aṣọ òkè | *woven material* |
| aṣọ léèsì | *lace material* |
| aṣọ tẹ́ẹ́rẹ́ | *strip of cloth* |
| àwọn ọlọ́lá | *rich people* |
| ẹ̀wùu kòlápá | *sleeveless clothing* |
| ibi iṣẹ́/ ibiṣẹ́ | *workplace* |
| ìgbà ooru | *hot weather* |
| ilẹ̀ òkèèrè | *foreign countries* |
| orílẹ̀-èdèe Àmẹ́ríkà | *USA* |
| látàrí ooru | *as a result of heat* |
| ṣòkòtò péńpé | *short pants/shorts* |

## Verbs

| | |
|---|---|
| dé/gẹ̀ | *to wear, e.g. a hat* |
| gbayì | *popular* |
| gbọ́dọ̀ | *must* |
| jẹ́ | *to be* |
| nípọn | *thick* |
| ró | *to wrap around* |
| wé | *to tie, e. g. a headgear* |
| wọ | *to wear ( clothes, shoes, or other apparel)* |
| wọ́n | *to be expensive* |

## Verb Phrases

| | |
|---|---|
| di ìgbàdí | *wrap-around waist* |
| fún … láàyè | *allow* |
| irú… wo? | *what type?* |

| | |
|---|---|
| kò pé | *not complete* |
| pa òwe | *say proverbially* |
| yàtọ̀ sí | *different from* |

## Adjectives

| | |
|---|---|
| oríṣiríṣi | *different types* |

## Conjunction

| | |
|---|---|
| tàbí | *or* |

## Prepositional phrase

| | |
|---|---|
| ní ọ̀nà mìíràn | *in another way* |

 CC – 2012 The University of Texas at Austin

## Lesson 1 - Ẹ̀kọ́ Kìíní:

## Aṣọ wíwọ̀ ní ilẹ̀ẹ Yorùbá *(Types of Clothing)*

Oríṣì aṣọ méjì pàtàkì ni àwọn Yorùbá máa ń wọ̀: aṣọ ojoojúmọ́ àti aṣọ ìmúròde. Aṣọ ojoojúmọ́ tí wọn máa ń wọ̀ ni aṣọ àǹkàrá àti aṣọ àdìrẹ. Aṣọ òde tí wọ́n máa ń wọ̀ ni aṣọ léèsì àti aṣọ òkè. Fún aṣọ ojoojúmọ́, àwọn obìnrin máa ń ró ìró, wọ́n máa ń wọ bùbá, wọ́n sì tún máa ń wé gèlè. Fún aṣọ òde àwọn obìnrin máa ń ró ìróo léèsì, wọ́n sì máa ń wọ bùbáa rẹ̀. Bákan náà ni fún aṣọ òkè. Wọ́n lè fi ìborùn lé tàbí kí wọ́n fi kọ́ èjìká. Ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn ọ̀dọ́mọbìnrin ni wọ́n máa ń so ìborùnun wọn mọ́ ìdí lode-òní.

Fún aṣọ ìmúròde àwọn ọkùnrin máa ń wọ ṣòkòtòo léèsi tàbí aṣọ òkè. Wọn máa ń wọ bùbáa léèsì tàbí aṣọ òkè. Wọ́n sì máa ń dé fìlà. Gèlè wíwé jẹ́ ara àwọn àṣà ìmúra tí ó gbayì lááárín àwọn obìnrin. Oríṣiríṣi gèlè ni ó wà. Wọn máa ń pe gèlè kan ní “kọjúsọ́kọ.” Awọn Yorùbá máa ń ṣe àpọ́nlé tí ó pọ̀ fún obìnrin tí ó bá mọ gèlèe wé dáradára. Nítorí ìdí èyí ni àwọn Yorùbá fi máa ń pá a ní òwe pé : “Gèlè òdùn bí i ká mọ̀ ọ́ wé, ká mọ̀ ọ́ wé kò tó kó yẹni.” Gèlè máa ń gbé ẹwà obìnrin yọ jáde gan-an ni.

Àwọn ènìyàn ti sọ ìborùn tó jẹ́ aṣọ tẹ́ẹ́rẹ́ tí wọ́n máa ń fi lé èjìkà di ìgbàdí tí wọ́n máa ń ró mọ́ ara ìró. Oríṣiríṣi ìró ni ó wà. Ìró aṣọ òkè jẹ́ èyí tí ó wọ́n jù. Nínú àwọn aṣọ òkè, “sányán” àti “àlàárì” jẹ́ méjì nínúu èyí tí àwọn ọlọ́lá àti ènìyàn pàtàkì máa ń wọ̀ jù. Àwọn obìnrin tún máa ń wọ “àrán.” Aṣọ àrán jẹ́ ọ̀kàn lára aṣọ tí wọ́n máa ń kó wá láti ilẹ̀ òkèèrè ní ayé àtijọ́.

Ní ilẹ̀ẹ Yorùbá, bí àwọn obìnrin ṣe máa ń wọ aṣọ́ yàtọ̀ sí bí àwọn ọkùnrin ṣe máa ń wọ̀ tiwọn. Fún aṣọ ìmúròde, lẹ́hìn tí àwọn ọkùnrin bá wọ ṣòkòtò àti bùbá, wọ́n á wọ agbádá léwọn. Ní ilẹ̀ẹ Yorùbá, fìlà dídé ṣe pàtàkì fún àwọn ọkùnrin. Ní ọ̀pọ̀lọpọ̀ ìgbá, apá òsì ni àwọn ọkùnrin máa ń sáábà gẹ fìlà sí. Ìmúra ọkùnrin kò pé tí kòbá dé fìlà, àti wí pé, iyì tí ó wà nínú ìmúra ni wí pé kí ọkùnrin dé fìlà. Oríṣiríṣi fìlá méjì ni ó gbayì púpọ̀ láàárin àwọn ọkùnrin: fìlá "ìkòrí" àti fìlà “a-betí-ajá”. Oríṣirísi ni aṣọ ti wọ́n fi ń ṣe àwọn fìlà yìí: aṣọ àǹkàrá, aṣọ àdìrẹ, asọ dàmáàsìkì àti aṣọ òkè. Fìlà gígẹ̀ jẹ́ ọ̀nà tí àwọn ọkùnrin máa ń gbà dé fìlà.

Àṣà ìbílẹ̀ẹ Yorùbá fún ọkùnrin àti obìnrin ní àyè bí wọ́n ṣe lè múra. Obìnrin kò gbọdọ̀ wọ ṣòkòtò, bẹ́ẹ̀ ni ọkùnrin kò gbọdọ̀ ró ìró. Bákan náà, obìnrin nìkan ni ó ní ẹ̀tọ́ láti wọ yẹtí. Fún ìdí èyí, àṣà kí obìnrin máa wọ ṣòkòtò tàbí kí ọkùnrin máa wọ yẹtí ní òde-òní jẹ́ àṣà tí ó wá láti ilẹ̀ òkèèrè.

 CC – 2012 The University of Texas at Austin

## Iṣẹ́ Ṣíṣe 1

Dáhùn àwọn ìbéèrè wọ̀nyí ní ẹ̀kúnrẹ́rẹ́.
*Answer the following questions in complete sentences.*

1. Oríṣi ìṣọ̀rí aṣọ mélòó ni àwọn Yorùbá ní? Dárúkọ wọn.
2. Irú àwọn aṣọ wo ni àwọn Yorùbá máa ń wọ̀ lọ sí àwọn òde pàtàkì?
3. Báwo ni àwọn obìnrin Yorùbá ṣe máa ń múra gẹ́gẹ́ bí àṣà ìbílẹ̀ẹ Yorùbá?
4. Báwo ni àwọn ọ̀dọ́mọbìnrin ṣe ń lo ìborùn ní ayé òde-òní?
5. Irú oríṣi ìró mélòó ni àwọn obìnrin máa ń ró ni ilẹ́ẹ Yorùbá? Èwo ni ó wọ́n jù nínúu wọn?
6. Kí ni ìyàtọ̀ tí ó wà láàárín aṣọ obìnrin àti ti ọkùnrin ní ilẹ̀ẹ Yorùbá?
7. Báwo ni àwọn ọkùnrin Yorùbá ṣe gbọ́dọ̀ múra ni ilẹ̀ẹ Yorùbá?
8. Apá ibo ni wọ́n sáábà máa ń gẹ fìlà sí ní ilẹ̀ẹ Yorùbá?
9. Kí ni àwọn ohun tí àṣà aṣọ wíwọ̀ ní ilẹ̀ẹ Yorùbá kò fàyè gbà fún ọkùnrin àti obìnrin láti wọ̀?
10. Kí ni èròo rẹ nípa àṣà aṣọ wíwọ̀ ní ilẹ̀ẹ Yorùbá?

## Iṣẹ́ Ṣíṣe 2

Sọ **bẹ́ẹ̀ ni** tàbí **bẹ́ẹ̀ kọ́** fún àwọn gbólóhùn wọ̀nyìí
*State whether the following sentences are **true** or **false***

| | BẸ́Ẹ̀ NI | BẸ́Ẹ̀ KỌ́ |
|---|---|---|
| 1. Ìṣọ̀rí aṣọ mẹ́ta pàtàkì ni àwọn Yorùbá máa ń wọ̀ | ☐ | ☐ |
| 2. Aṣọ ìmúròde tí awọ́n Yorùbá máa ń wọ̀ ni aṣọ àǹkàrá àti aṣọ àdìrẹ | ☐ | ☐ |
| 3. Àwọn ọkùnrin Yorùbá máa ń wọ̀ bùbá àti ṣòkòtò | ☐ | ☐ |
| 4. Ní ilẹ̀ẹ Yorùbá bákan náà ní aṣọ ti àwọn ọkùnrin àti ọbìnrin. | ☐ | ☐ |
| 5. Obìnrin le wọ̀ ṣòkòtò ní ilẹ̀ẹ Yorùbá | ☐ | ☐ |

 CC – 2012 The University of Texas at Austin

## Iṣẹ́ Ṣíṣe 3

Parí àwọn gbólóhùn wọ̀nyí.
*Complete the following sentences.*

1. Àwọn Yorùbá máa ń wọ irú oríṣi aṣọ
   a. mẹ́ta
   b. mẹrin
   c. mẹ́fà
   d. méjì

2. Nínúu àṣàa Yorùbá ni kí ọbìnrin lo_______________.
   a. fìlà
   b. yẹtí
   c. ṣòkòtò
   d. agbádá

3. Àwọn ọkùnrin Yorùbá máa ń wọ _______________.
   a. fìlà
   b. kaba
   c. ìró
   d. agbádá

4. _______________ṣe pàtàkì nínú ìmúra àwọn ọkùnrin Yorùbá.
   a. fìlà
   b. ṣòkòtò
   c. bùbá
   d. agbádá

5. _______________jẹ́ ọ̀kan lára aṣọ ilẹ̀ òkèèrè.
   a. aṣọ òkè
   b. àdìrẹ
   c. aṣọ àrán
   d. aṣọ léèsì

 CC – 2012 The University of Texas at Austin

### Iṣẹ́ Ṣíṣe 4
Dáhùn àwọn ìbéèrè wọ̀nyí.
*Answer the following questions.*

Irú aṣọ wo ni àwọn Yorùbá máa ń wọ̀ lọ sí...?

1. ọjà
2. ibi ìgbéyàwó
3. ibi ìsọmọlórúkọ
4. ibiṣẹ́
5. ṣọ́ọ̀ṣì / ilé-ìsinmi

### Iṣẹ́ Ṣíṣe 5
Nibo ni àwọn Yorùbá máa ń wọ àwọn aṣọ wọ̀nyí lọ?
*Where do Yorùbá people wear these clothes to?*

1. aṣọ àdìrẹ
2. aṣọ àǹkàrá
3. aṣọ léèsì
4. aṣọ òkè
5. aṣọ dàmáásìkì

 CC – 2012 The University of Texas at Austin

# Lesson 2 - Ẹ̀kọ́ Kejì:

# More Interrogatives

The following models illustrate the use of interrogatives such as: *'kí ni', 'ta ni', 'nígbà wo', 'níbo', 'kí ló', 'báwo' and 'èwo'.*

## Who?

| | | |
|---|---|---|
| Q. | Ta ni ó wà nínúu yàrá nàá? | *Who is inside the room?* |
| R. | Ìdáhùn: Kò sí ẹnì kankan nínúu yàrá nàá. | *Nobody is inside the room.* |
| Q. | Ìwée ta ni yìí? | *Whose book is this?* |
| R. | Ìwée Títí ni. | *It's Títí's book.* |
| Q. | Ta ni o fẹ́ràn ni ilé-ìwéè rẹ? | *Who do you like in your school?* |
| R. | Mo fẹ́rànan olùkọ́ọ̀ mi. | *I like my teacher.* |

## What?

| | | |
|---|---|---|
| Q. | Kí ni ò ń ṣe nísìnyí? | *What are you doing now?* |
| R. | Mò ń ka ìwéè mi. | *I'm reading my book.* |
| Q. | Kí nì yìí? | *What is this?* |
| R. | Aáyán ńlá ni. Yéèpà! | *It's a big cockroach. Wow!* |
| Q. | Kí ní ò ń kà? | *What are you reading?* |
| R. | Mò ń ka ìwèé Ṣóyínká ni. | *I'm reading a book by Ṣóyínká .* |

## When?

| | | |
|---|---|---|
| Q. | Nígbà wo ni ọjọ́-ìbî rẹ? | *When is your birthday?* |
| R. | Ọ̀la ni. | *It's tomorrow.* |

## Where?

| | | |
|---|---|---|
| Q. | Níbo ni ò ń gbé? | *Where do you live?* |
| R. | Ní ẹ̀gbẹ́ ọjà ni mò ń gbé | *I live near the market.* |

**Why?**

| | | |
|---|---|---|
| Q. | Kí ló dé tí ò ń sunkún? | *Why are you crying?* |
| R. | N kò rí àpò owóò mi. | *I cannot find my wallet.* |

**How?**

| | | |
|---|---|---|
| Q. | Báwo ni? | *How are you?* |
| R. | Dáadáa ni? | *I'm fine.* |
| Q. | Báwo ni o ṣe máa dé ọjà? | *How will you get to the market?* |
| R. | Mà á gun kẹ̀kẹ́ẹ̀ mi ni. | *I will ride my bicycle.* |

**Which one?**

| | | |
|---|---|---|
| Q. | Èwo nínú àwọn ọ̀dọ́mọdékùnrin yẹn ni o fẹ́ràn? | *Which of those boys do you like?* |
| R. | Túndé ni mo fẹ́ràn. | *I like Túndé.* |
| Q. | Títì wo ló lọ sí ṣọ́ọ̀ṣì? | *Which street leads to the church?* |
| R. | Títi ọwọ́ òsì ni. | *The street on the left.* |

## Iṣẹ́ Ṣíṣe 1

Fi àṣebéèrè tó bá yẹ dí àwọn àlàfo wọ̀nyí
*Fill in the spaces below with the appropriate interrogative.*

____________ nínú ẹ̀yin akẹ́kọ̀ọ́ ni ọjọ́ ìbíi rẹ̀ jẹ́ ọ̀la? ____________ ni o ti máa ṣe ọdún ìbíi yìí? ____________ ni o ṣe máa má ṣe é? ____________ o fẹ́ ṣe ọjọ́ ìbíi yìí pẹ̀lú? ____________ ni ọdún ìbíi yìí máa parí?

## Iṣẹ́ Ṣíṣe 2

Lo àwọn àṣebéèrè wọ̀nyí látì ṣẹ̀dáa gbólóhùn.
*Use the following interrogatives to form sentences.*

1. Kí ni?
2. Ta ni?
3.Níbo ni?
4. Kí lódé?
5. Báwo ni?

## Lesson 3 - Ẹ̀kọ́ Kẹta:

## Verbs fi_lé/fi_ kọ́, wọ̀, dé, wé, ró, gẹ̀

The following verbs are used with clothing: fi_lé/ fi_ kọ́, wọ̀, dé, wé, ró, gẹ̀. For instance:
Àwọn ọkùnrin máa n *wọ* bùbá àti agbádá. Wọ́n máa n *dé* fìlà.

Àwọn obìnrin máa n *wọ* bùbá, ró ìró, *wé* gèlè. Wọ́n sì máa n *fi* ìborùn *kọ́ / lé* èjìká
The verb "gẹ̀" can be used for both "gèlè" and "fìlà".

**Bí àpẹẹrẹ:**

Ọkùnrin ń gẹ fìlà.

Obìnrin ń gẹ gèlè.

However, **dé** and **wé** are general terms while **gẹ̀** denotes a particular style of headgear or hat. Below are the different types of clothes for men and women and the manner in which they are worn in Yorùbáland.

| Aṣọ okùnrin (Male clothes) | Aṣọ obìnrin (Female clothes) |
|---|---|
| bùbáa léèsì, ṣòkòtòo léèsì, agbádáa léèsì, fìlà aṣọ òkè tàbí fìlàa dàmáásìkì | bùbáa léèsì, ìróo léèsì, gèlèe léèsì tàbí gèlèe dàmáásìkì |
| bùbá àǹkàrá, ṣòkòtò àǹkàrá, agbádá àǹkàrá | bùbá àǹkàrá, ìró àǹkàrá, gèlè àǹkàrá |
| bùbá aṣọ òkè, ṣòkòtò aṣọ òkè, agbádá aṣọ òkè, fìlà aṣọ òkè | bùbá àǹkàrá, ìró àǹkàrá, gèlè gidi |
| dàńṣíkí, ṣòkòtò, fìlà | bùbá aṣọ òkè, ìró aṣọ òkè, gèlè aṣọ òkè<br>**tàbí**<br>bùbáa léèsì, ìró aṣọ òkè, gèlè aṣọ òkè<br>**tàbí**<br>bùbáa léèsì, ìróo léèsì, gèlè aṣọ òkè |

 CC – 2012 The University of Texas at Austin

## Ayé ń lọ à ń tọ̀ ọ́ (Fashion Trends)

Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé àṣàa Yorùbá ni pé kí obìnrin wọ bùbá, ró ìró, kí wọ́n sì tún wé gèlè, àti pé kí okùnrin wọ bùbá, wọ ṣòkòtò, kí wọ́n tún dé fìlà, oríṣi aṣọ mìíràn tún wà tí wọ́n le wọ̀. Ní òde-òní, oríṣiríṣi àrà ni àwọn ènìyàn ń fi aṣọ àǹkàrá, léèsì, àdìrẹ àtí gínnì dá. Bí ìgbà ṣe ń yí ni àṣà aṣọ wíwọ̀ náà ń yí láàrín àwọn Yorùbá. Kódà ọ̀làjú ti mú kí àṣà aṣọ wíwọ̀ àwọn Yorùbá di ohun tí àwọn ènìyàn láti ìlú òkèèrè ń wárí fún. Nítorí pé ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn Yorùbá ni wọ́n jẹ́ oníṣẹ́ ọba, ó ṣòró láti máa wọ bùbá àti ṣòkòtò, tàbí kì wọ́n máa ró ìró tàbí wé gèlè lọ sí ibi iṣẹ́ òòjọ́ọ wọn. Ìdí nìyí tó fi jẹ́ pé oríṣiríṣi àrà ni wọ́n ń fi àǹkàrá rán: bí i síkẹ́ẹ̀tì, bùláòsì, súùtù àti kaba. Àṣà fífi àwọn aṣọ bíi àǹkàrá, léèsì, gínnì ati àdìrẹ dá àrà lóríṣiríṣi ti gbilẹ̀ ní ilẹ̀ẹ Yorùbá tó fi jẹ́ pé púpọ̀ nínú àwọn télọ̀ (aránṣọ) ni ó ti di olówó àti gbajúmọ̀ nípa bẹ́ ẹ̀.

Nítorí pé wọ́n ti ń fi àwọn aṣọ yìí dá oríṣiríṣi àrà, àwọn ènìyàn bíi olùkọ́, ọ̀jọ̀gbọ́n, oníròyìn àti akọ̀wé lè wọ àǹkàráa súùtù, tàbí àdìrẹ búláòsì àtí síkẹ́ẹ̀tì lọ sí ibí iṣẹ́. Ṣùgbọ́n àwọn iṣẹ́ kan wà tí a kò lè wọ àwọn irú aṣọ báyìí lọ bí ó ti wù kí ó mọ. Àwọn irú iṣẹ́ báyìí ni iṣẹ́ẹ agbẹjọ́rò, iṣẹ́ àkàtàǹtì àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Dandan ni fún àwọn agbẹjọ́rò àti òṣìṣẹ́ ilé ìfowópamọ́ láti wọ súùtù òyìnbó àti táì lọ sí ibi iṣẹ́ẹ wọn. Fún ìdí èyí, àṣà aṣọ wíwọ̀ láàárín àwọn Yorùbá ti yí wọnú araa wọn.

Bó ti lẹ̀ jẹ́ pé ìró, bùbá, gèlè àti ìborùn jẹ aṣọ ìbílẹ̀ tí obìnrin Yorùbá máa ń wọ̀, tí bùbá, ṣòkòtò àtí fìlà sì jẹ́ aṣọ ìbílẹ̀ fún àwọn ọkùnrin Yorùbá, wọ́n tún máa ń wọ àwọn aṣọ òyìnbó gẹ́gẹ́ bí iṣẹ́ tí wọ́n bá ń ṣe bá ṣe rí. Nítorí ìdí èyí ni àwọn Yorùbá ṣe máa ń pa òwe pé, “bí ẹyẹ bá ṣe fò ní a ṣe ń sọ́kòo rẹ̀”. Èyí túmọ̀ sí pé bí ìgbà bá ṣe rí ni a ṣe ń lò ó. Bí àwọn ọkùnrin Yorùbá bá wọ súùtù òyìnbó lọ síbi iṣẹ́ wọn, wọn á de táì, de bẹ́lítì sí ṣòkòtòo wọn. Wọn a wọ ìbọ̀sẹ̀ àti bàtà. Wọn á dì bíi akọ̀wé. Àwọn obìnrin Yorùbá pàápàá tó ń ṣiṣẹ́ ìjọba náà á wọ súùtù tàbí kí wọ́n wọ síkẹ́ẹ̀ti àti búláòsì. Wọ́n á sì tún wọ bàtà òyìnbó. Gbogbo wọn á máa tẹlẹ̀ “ko-ko-kà”. Lóòótọ́ ayé ti dayé ọ̀làjú. Gbogbo nǹkan ló sì ti yí padà.

 CC – 2012 The University of Texas at Austin

## Iṣẹ́ Ṣíṣe 1

Dáhùn àwọn ìbéèrè wọ̀nyí.
*Answer the following questions.*

1. Báwo ni àwọn ọkùnrin àtí obìnrin Yorùbá ṣe máa ń wọṣọ tàbí múra gẹ́gẹ́ bí àṣàa Yorùbá?
2. Kí ló dé tí àwọn ará ìlú òkèèrè fi ń wárí fún àṣà asọ wíwọ̀ láàrín àwọn Yorùbá lóde-òní?
3. Kí ni ìdí rẹ́ tí wọ́n fi ń fi àwọn aṣọ ìbílẹ̀ bíi ànkàrá dá oríṣiríṣi àrà ní òde-òní?
4. Yàtọ̀ si bùbá, ìró àtí ṣòkòtò, kí ni a tún le fi àǹkárá, léèsì tàbí àdìrẹ rán ?
5. Kí ni nǹkan pàtàkì tí fifi àwọn aṣọ ìbílẹ̀ dá oríṣiríṣi àrà ti ṣe fún àṣàa Yorùbá?
6. Kí ni ìdí rẹ̀ ti àwọn ènìyàn bíi agbẹjọ́rò àti òsìṣẹ́ ilé ìfowópamọ́ kò ṣe lè wọ àwọn aṣọ ìbílẹ̀ lọ síbi iṣẹ́?
7. Kí ni èrò rẹ nípa bí ó ti jẹ́ dandan fún àwọn agbẹjọ́rò láti wọ súùtù òyìnbó lọ síbi iṣẹ́?
8. Kí ló dé tí àwọn Yorùbá fi máa ń pa òwe pé "bí ẹyẹ ṣe fò ni a ṣe ń sọ̀kòo rẹ̀?"
9. Sọ ìyàtọ̀ tó wà láàárín aṣọ iṣẹ́ obìnrin àtí ọkùnrin tí ó ń ṣisé ìjọba.
10. Ǹjẹ́ àǹfààní kankan wà nínú ọ̀làjú tí àwọn Yorùbá gbà láàyè nínú àṣà aṣọ wíwọ̀ọ wọn?

## Iṣẹ́ Ṣíṣe 2

So àwọn tí ó bara mu ni ọ̀wọ́ A àti ọ̀wọ́ B papọ̀.
*Match the words in column A with those in column B.*

| A | B |
|---|---|
| gèlè | wọ |
| fìlà | wé |
| ìró | fi_ lé /fi_kọ́ èjìkàá |
| ṣòkòtò | dé |
| ìborùn | ró |

 CC – 2012 The University of Texas at Austin

## Iṣẹ́ Ṣíṣe 3

Wá àwọn ọ̀rọ̀ wọ̀nyí

*Look for these words in the puzzle below. Pay attention to the tones!*

**aṣọ, bùbá, fìlà, gèlè, ìborùn, ìró, ìsọmọlórúkọ, iyì, ọjà, ṣòkòtò**

| | | | | | | | | | | | | | | |
|---|---|---|---|---|---|---|---|---|---|---|---|---|---|---|
| i | r | o | u | ṣ | ò | k | ò | t | ò | i | b | o | r | a |
| u | a | t | m | è | f | ọ | o | g | b | á | d | e | b | s |
| a | s | a | b | o | ì | g | j | s | e | a | d | è | i | o |
| b | ù | b | á | i | l | è | r | à | d | l | o | d | b | p |
| i | l | è | k | u | à | ì | r | ó | f | a | e | j | o | o |
| b | í | b | í | l | a | r | í | l | è | p | a | g | r | l |
| i | j | a | ì | s | ọ | m | ọ | l | ó | r | ú | k | u | o |
| l | o | g | è | b | a | l | u | m | a | f | b | ú | n | n |
| a | d | è | p | a | o | i | y | i | n | i | u | i | j | i |
| b | u | l | á | g | u | r | è | p | è | t | b | á | y | á |
| u | g | è | í | b | a | d | ù | f | i | l | a | g | b | ì |
| g | b | á | j | u | m | á | p | n | í | g | b | a | d | u |
| ú | ì | s | ọ | m | ọ | l | ó | r | ú | k | ọ | è | b | è |
| i | k | e | j | p | o | p | o | l | á | a | j | a | g | b |
| a | ṣ | ọ | a | j | s | o | k | o | t | o | g | b | e | j |

 CC – 2012 The University of Texas at Austin

## Iṣẹ́ Ṣíṣe 4

Parí àwọn gbólóhùn wọ̀nyí ní ẹ̀kúnrẹ́rẹ́.
*Complete the following sentences.*

1. ______________kì í ṣe ọ̀kan lára àwọn aṣọ obìnrin láwùjọ Yorùbá.
   a. Bùbá
   b. Ìró
   c. Gèlè
   d. Fìlà

2. Àwọn ọkùnrin Yorùbá kí ì wọ ________________
   a. bùbá
   b. agbádá
   c. búláòsì
   d. súùtù

3. Àwọn ọkùnrin Yorùbá máa ń wọ ______________.
   a. gèlè
   b. ìró
   c. ìborùn
   d. bùbá

4. ________________ kì í ṣe aṣọ ìbílẹ̀ẹ  Yorùbá.
   a. Aṣọ àǹkárá
   b. Aṣọ léèsì
   c. Aṣọ àdìrẹ
   d. Aṣọ súùtù

5. ________________ kì í ṣe aṣọ tí àwọn ènìyàn ń wọ̀ lọ sí ibi iṣẹ́ ní òde-òní.
   a. Súùtù òyìnbó
   b. Síkẹ́ẹ̀ti
   c. Búláòsì
   d. Bùbá

## Iṣẹ́ Ṣíṣe 5

State the equivalence of this proverb in English and explain its relevance in today's activities.
"bí ẹyẹ bá ṣe fò ní a ṣe ń sọ́kòo rẹ̀"


CC – 2012 The University of Texas at Austin

## Ìlẹ̀kẹ̀ títò ní ilẹ̀ẹ Yorùbá

Àwọn Yorùbá jẹ́ akíkanjú nínú iṣẹ́ ọwọ́ ṣíṣe. Wọn kì í ṣe ọ̀lẹ tàbí ìmẹ́lẹ́. Wọ́n jẹ́ ènìyàn tí ó tẹ́pá mọ́ṣẹ́. Nínú àwọn iṣẹ́ ọwọ́ tí wọ́n máa ń ṣe ni aṣọ òkè híhun, ẹní apẹ̀rẹ̀ híhun, aṣọ pípa láró, apẹ̀ẹ̀rẹ̀ híhun, ẹyìn fífọ̀, ìlẹ̀kẹ̀ sínsín àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ.

Àwọn ènìyàn pàtàkì bíi ìdílé Ọba, ìdílé oyè àti ìdílé ọlà ní wọ́n máa ń wọ ìlẹ̀kẹ̀ ní ayé àtijọ́. Ìlẹ̀kẹ̀ tí ó sí wọ́pọ̀ nígbà náà ni iyùn. Iyùn jẹ́ ìlẹ̀kẹ̀ olówó iyebíye. Ṣùgbọ́n ní òde-òní, nǹkan tí yàtọ̀. Gbogbo ènìyàn tí o bá wù ni ó lè lo ìlẹ̀kẹ̀. Kò sì pọn dandan pé kí ó jẹ́ iyùn. Idí ni pé oríṣiríṣi ìlẹ̀kẹ̀ ní ó ti wà ní òde-òní nítorí ìmọ̀-ẹ̀rọ tí ó ń gbilẹ̀ jẹ́ kí a lè rí ìlẹ̀kẹ̀ oníke dípò ìlẹ̀kẹ̀ gidi. Àpẹẹrẹ àwọn ìlẹkẹ̀ gidi ni ojú ológbò, ìlẹ̀kẹ̀ fífọ́, kírísítààlì. Oríṣiríṣi nǹkan ní a lè to ìlẹ̀kẹ̀ fún. A lè to ìlẹ̀kẹ̀ láti fi ṣe ẹ̀gbà ọrùn, ẹ̀gbà ọwọ́, ẹ̀gbà ẹsẹ̀, bàtà ẹsẹ̀, àpò ìmúròde àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Onírúurú ni àwọ̀ àwọn ìlẹ̀kẹ̀ tí ó wà ní òde-òní – pupa, funfun, dúdú, àti búlúù.

### Iṣẹ́ Ṣíṣe 6

Dáhùn àwọn ìbéèrè wọ̀nyí ní ẹ̀kúnrẹ́rẹ́.
*Answer the following questions in complete sentences.*

1. Irú ènìyàn wo ni àwọn Yorùbá?
2. Dárúkọ iṣẹ́ ọwọ́ tí àwọn Yorùbá máa ń ṣe.
3. Irú àwọn ènìyàn wo ni wọ́n ń lo ìlẹ̀kẹ̀ ní ilẹ̀ẹ Yorùbá?
4. Kí ni ó fà á tí ìlẹ̀kẹ̀ oníke fi wà ní ayé òde-òní?
5. Dárúkọ irú àwọn àwọ̀ ìlẹ̀kẹ̀ tí wọ́n wà ní ayé òde-òní.

### Iṣẹ́ Ṣíṣe 7

Kọ ìtumọ̀ àwọn ọ̀rọ̀ wọ̀nyí sílẹ̀ ní èdèe Yorùbá.
*Write the meanings of these words in Yorùbá.*

1. Akínkanjú
2. Iyùn
3. Ìdílé oyè
4. Ọ̀làjú
5. Àṣà

 CC – 2012 The University of Texas at Austin

### Iṣẹ́ Ṣíṣe 8

Parí àwọn gbólóhùn wọ̀nyí.
*Complete the following sentences.*

Àwọn Yorùbá jẹ́ ènìyàn ____________ . Wọn kì í ṣe ____________. Lára àwọn iṣẹ́ tí wọ́n máa ń ṣe ni ____________ . Ní ayé àtijọ́, àwọn ìdílé ____________ ni wọ́n máa ń wọ ìlẹ̀kẹ̀ tẹ́lẹ̀ ṣùgbọ́n ní òde-òní, gbogbo ènìyàn ló lè lo ìlẹ̀kẹ̀ nítorí ____________ tí ó ti gba ayé kan. ____________ jẹ́ ìlẹ̀kẹ̀ tí ó pàtàkì láwùjọ Yorùbá.



 CC – 2012 The University of Texas at Austin

## Lesson 4 - Ẹ̀kọ́ Kẹrin:
## Seasonal Clothings

Ọríṣiríṣi aṣọ ni àwọn ènìyàn máa ń wọ ní àsìkòo fọ́ọ̀lù, wíńtà, sípíríǹgì, sọ́mà àti àkókò ọyẹ́.

**Bí àpẹẹrẹ:**

**Ní fọ́ọ̀lù**

- súwẹ́tà tí kò nípọn
- jákẹ́ẹ̀tì
- jíìnsì
- tíṣẹẹ̀tì

**Ní wíńtà**

- kóòtù wíńtà
- súwẹ́tà
- ìbọ̀wọ́
- ìbọsẹ̀

**Ní sípíríngì**

- súwẹ́tà tí ó nípọn
- jákẹ́ẹ̀ti
- jíìnsì

**Ní sọ́mà**

- ṣọ́ọ̀ti
- tíṣẹẹ̀tì
- síńgílẹ́ẹ̀tì
- búláòsì

### Aṣọ òjò ní ẹ̀ẹ̀rùn

Àwọn Yorùbá ní ìgbàgbọ́ pé kò yẹ kí ènìyàn máa wọ aṣọ òjò ní ẹ̀ẹ̀rùn nítorí pé ìgbà ara ni à á búra, ẹnìkan kì í bú Ṣàngó ní ẹ̀ẹ̀rùn. Oríṣiríṣi aṣọ ni àwọn ènìyàn máa ń wọ̀ ní àkókò kọ̀ọ̀kan. Aṣọ òjò yàtọ̀ sí ti ẹ̀rùn, bẹ́ẹ̀ ti ọyẹ́ kò fi ara jọ ti ìgbà ooru. Bí ó ṣe wà ní ilẹ̀ẹ Yorùbá náà ni ó wà ní gbogbo ibi tí ó fi dé orílẹ̀-èdèe Àmẹ́ríkà.

Àsìkò mẹ́rin ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀ ni a lè rí ní orílẹ̀-èdè Àmẹ́ríkà. Àsìkòo wíńtà, sípíríǹgì, sọ́mà àti fọ́ọ̀lù. Ní gbogbo àwọn àsìkò yìí, oríṣiríṣi aṣọ ni àwọn ènìyàn máa ń wọ̀. Ní àsìkòo wíńtà, àwọn ènìyàn máa ń wọ àwọn aṣọ bíi kóòtù, súwẹ́tà, ìbọ̀wọ́ àti ìbọsẹ̀. Àsìkò sípíríǹgì, ni àwọn ènìyàn máa ń wọ súwẹ́tà tí ò nípọn, jákẹ́ẹ̀tì àti jíìnsì.

Ní àsìkòo sọ́mà, àwọn aṣọ tí kò nípọn rárá bí i ẹ̀wùu kòlápá, ṣòkòtò péńpé, síkẹ́ẹ̀tì àti búláòsì ni àwọn ènìyàn máa ń wọ̀ látàrí ooru tí ó máa ń mú ni àsìkò yìí. Tí ó bá wá di àsìkòo fọ́ọ̀lù, nítorí pé òtútù ti máa ń fẹ́ bẹ̀rẹ̀ láti mú. Àwọn ènìyàn máa ń wọ àwọn aṣọ bí i súwẹ́tà tí kò nípọn, jákẹ́ẹ̀tì, jíìnsì àti tísẹ̀ẹ̀tì.

## Iṣẹ́ Ṣíṣe 1

Dáhùn àwọn ìbéèrè wọ̀nyí ní ẹ̀kúnrẹ́rẹ́.
*Answer the following questions in complete sentences.*

1. Kí ni ó dé tí ènìyàn kò fi lè wọ aṣọ òjò ní ẹ̀ẹ̀rùn?
2. Ṣàlàyé ohun tí ó máa ń ṣẹlẹ̀ ní àsìkòo wíńtà.
3. Irú aṣọ wo ni àwọn ènìyàn máa ń wọ̀ ní àsìkòo sípíríǹgì?
4. Ṣé lóòótọ́ ni pé aṣọ ti kò nípọn ni àwọn ènìyàn máa ń wọ̀ ní àsìkòo fọ́ọ̀lù? Ṣe àlàyé.
5. Tí ó bá di àsìkòo sọ́mà, irú aṣọ wo ni ìwọ́ fẹ́ràn láti máa wọ̀?

 CC – 2012 The University of Texas at Austin

## Iṣẹ́ Ṣíṣe 2

Parí àwọn gbólóhùn wọ̀nyí.
*Complete the following sentences.*

1. Àwọn Yorùbá máa ń bú Ṣàngó ní_______________?
    a. àsìkòo fọ́ọ̀lù
    b. àsìkòo wíńtà
    c. àsìkò ẹ̀ẹ̀rùn
    d. àsìkò òjò

2. Irú àsìkò mélòó ni a le rí ní orílẹ̀-èdè Àmẹ́ríkà?
    a. mẹ́ta
    b. méjì
    c. mẹ́fà
    d. mẹ́rin

3. Àsìkò mélòó ni a le rí ní orílẹ̀-èdè Nàìjíríà?
    a. mẹ́ta
    b. méjì
    c. mẹ́fà
    d. mẹ́rin

4. Ní àsìkò sọ́mà, àwọn ènìyàn máa ń wọ____________?
    a. kóòtù
    b. súwẹ́tà
    c. ìbọ̀wọ́
    d. ṣòkòtò péńpé

5. _________________ jẹ́ aṣọ tí àwọn ènìyàn máa ń wọ̀ jù ní àsìkòo wíńtà?
    a. Jákẹ́ẹ̀tì
    b. Jîìnsì
    c. Tíṣẹ̀ẹ̀tì.
    d. Kóòtù


CC – 2012 The University of Texas at Austin

## Iṣẹ́ Ṣíṣe 3

Sọ **bẹ́ẹ̀ ni** tàbí **bẹ́ẹ̀ kọ́** fún àwọn gbólóhùn wọ̀nyìí
*State whether the following sentences are **true** or **false***

| | BẸ́Ẹ̀ NI | BẸ́Ẹ̀ KỌ́ |
|---|---|---|
| 1. Àwọn Yorùbá fẹ́ràn aṣọ òjò ní ẹ̀ẹ̀rùn. | ☐ | ☐ |
| 2. Kò sí ìyàtọ̀ láàrin àsìkò òjò àti àsìkò ẹ̀rùn ní orílẹ̀-èdè Nàìjíríà. | ☐ | ☐ |
| 3. Òtútù máa ń pọ̀ ní àsìkòo fọ̀ọ̀lù ju àsìkòo wíńtà lọ. | ☐ | ☐ |
| 4. Tíṣẹ̀ẹ̀tì ni àwọn ará orílẹ̀-èdè Àmẹ́ríkà máa ń wọ̀ ní àsìkòo wíńtà. | ☐ | ☐ |
| 5. Àsìkò méjì péré ni a lè rí ní orílẹ̀-èdè Àmẹ́ríkà. | ☐ | ☐ |

## The Interrogative ‘Nígbà wo?’, and ‘Nígbà tí’

**Nígbà wo** is an interrogative marker that denotes ***when***. **Nígbà tí** can be used as a response to **nígbà wo**.

**For instance:**

| | |
|---|---|
| **Nígbà wo** ni wà á lọ sí ilé?<br>Mà á lọ sí ilé **nígbà tí** mo bá parí ìwé tí mò ń kà. | *When are you going home?*<br>*I will go home when I finish with the book I'm reading.* |
| **Nígbà wo** ni ilé-ẹ̀kọ́ gíga Yunifásítì tiTexas ní Austin ń bẹ̀rẹ̀ lọ́dún? | *When does the school year begin at the University of Texas at Austin?* |
| Ní oṣù kẹjọ ọdún ni. | *It’s in the eighth month of the* year. |

 CC – 2012 The University of Texas at Austin

## Iṣẹ́ Ṣíṣe 4

Dáhùn àwọn ìbéèrè wọ̀nyí.
*Answer the following questions.*

1. Nígbà wo ni àsìkò òjò ni ìlúù rẹ?
2. Nígbà wo ni o máa ń jẹun àárọ̀?
3. Nígbà wo ni bàbáa rẹ máa ń ti ibi iṣẹ́ dé?
4. Nígbà wo ni wà á lọ sí ọjà?
5. Nígbà wo ni o máa ń sùn?
6. Nígbà wo ni o máa ń wọ aṣọ òtútù?
7. Nígbà wo ni àsìkò ẹ̀rùn ni ìlúù rẹ?
8. Irú aṣọ wo lo fẹ́ràn láti wọ̀ nígbàa sọ́mà?
9. Irú aṣọ wo lo fẹ́ràn láti wọ̀ nígbà òjò?
10. Nígbà wo ni àsìkò òtútù ni ìlúù rẹ?

## Iṣẹ́ Ṣíṣe 5

O yà, ó kàn ẹ̀. Lo 'nígbà wo' láti bèèrè lọ́wọ́ ọ̀rẹ́ẹ̀ rẹ ohun tí ó máa ń ṣe ní ọ̀sẹ̀. Má ṣe jẹ́ kí ó ju ìbéèrè márùn-ún lọ.

It's now your turn. Use 'nígbà wo' to ask your friend some questions. Do not ask more than five questions.

## Iṣẹ́ Ṣíṣe 6

Dáhùn àwọn ìbéèrè wọ̀nyí.
*Answer the following questions.*

1. Nígbà wo ni àwọn Yorùbá máa ń wọ súwẹ́tà?
2. Nígbà wo ni àwọn ọmọ ìlú Àmẹ́ríkà máa ń wọ kóòtù àti ìbọ̀wọ́?
3. Ṣé ènìyàn lè wọ ṣọ́ọ̀ti ní àkókòo wíńtà?
4. Nígbà wo ni àwọn ọmọ ìlú Àmẹ́ríkà máa ń wọ aṣọ péńpé?
5. Nígbà wo ni ìwọ máa ń fẹ́ràn láti wọ jákẹ́ẹ̀tì?

 CC – 2012 The University of Texas at Austin




# Chapter 12 - Orí Kejìlá | CAMPUS LIFE

## *OBJECTIVES:*

In this chapter you will learn:

- About the school system
- How to tell your friend about your course schedule
- How to describe your school's facilities to your friend
- About life on campus

# Àwọn ọ̀rọ̀ (*Vocabulary*)

| Nouns | |
|---|---|
| áàtì/ọnà | *arts* |
| adájọ́ | *judge* |
| agbára | *strength* |
| agbègbè | *area* |
| àjànàkú / erin | *elephant* |
| akẹ́gbẹ́ẹ | *colleague* |
| àkọ́dá | *first to establish* |
| àkọ́sórí | *memory verse* |
| alákòóso | *governing council* |
| àǹfààní | *opportunity* |
| apá | *section/arm* |
| àpọ́nlé | *exaggeration* |
| àyè | *opportunity* |
| àyẹ̀wò | *experiment* |
| BÍ-EÈ | *B.A.* |
| BÍ-Ẹ̀ẸDÌ | *B. Ed.* |
| BÍ-Ẹ̀ẸSÌ | *B.Sc.* |
| dáná | *cook* |
| èsì | *result(s)* |
| ẹ̀kọ́ | *course(s)* |
| ẹlòmîn | *another person* |
| Ẹ́M-EÈ | *M.A.* |
| Ẹ́M-Ẹ̀ẸDÌ | *M. Ed.* |
| Ẹ́M-Ẹ̀ẸSÌ | *M. Sc.* |
| ẹnjiníà | *engineer* |
| ibùgbé | *residence* |
| ibùjókòó | *office* |
| ìdárayá | *entertainment* |
| ìdánwò | *examination* |
| ìgboyè | *the degree of* |
| Ilé-ìkàwé | *library* |
| imọ̀-ẹ̀kọ́ | *education (as a discipline)* |
| Ìmọ̀-ẹ̀rọ | *engineering (as a discipline)* |

| | |
|---|---|
| irun | *hair* |
| ìṣẹ́jú | *minute* |
| ìṣirò | *math* |
| ìṣòro | *challenges, problems* |
| kàǹtíìnì | *canteen/restaurant* |
| kẹ́míkà | *chemical* |
| kíkẹ́kọ̀ọ́ | *the study of* |
| kọ́kọ́ | *first* |
| láàbù | *laboratory* |
| lítíréṣọ̀ | *literature* |
| obìnrin | *female* |
| odindin | *whole* |
| ojoojúmọ́ | *everyday* |
| oko | *farm* |
| olùkọ́ | *teacher* |
| òmìnira | *independence* |
| ọmọwé | *a person who holds a Ph.D* |
| oníròyìn | *journalist* |
| òtítọ́ | *truth* |
| ósítẹ̀lì | *hostel* |
| ọkùnrin | *male* |
| ọ́ọ̀lù | *hall* |
| òpópónà | *street* |
| ọ̀tun | *new* |
| politẹ́kíníìkì | *polytechnic* |
| sáyẹ́ǹsì | *science* |
| simẹ́sítà/sáà | *semester* |
| títì | *street* |
| wákàtí | *hour* |

## Noun Phrases

| | |
|---|---|
| bọ́ọ̀lù àfẹsẹ̀gbá | *soccer* |
| bọ́ọ̀lù àfọwọ́gbá | *handball* |
| bọ́ọ̀lù àjùsáwọ̀n | *basketball* |
| òfin àti ìlànà ìtọ́ sọ́nà | *rules and regulations* |
| ẹ̀ka ẹ̀kọ́ | *branches of study* |

 CC – 2012 The University of Texas at Austin

| | |
|---|---|
| Ẹ̀ka àṣà àti ijó | *Department of Culture and Dance* |
| Ẹ̀ka ẹ̀kọ́ọ olùkọ́ni | *Faculty of Education* |
| Ẹ̀ka ẹ̀kọ́ iṣẹ́-ọnà | *Faculty of Arts* |
| Ẹ̀ka ẹ̀kọ́ iṣẹ́ àgbẹ̀ | *Faculty of Agriculture* |
| ẹ̀kọ́ èdèe Yorùbá<br>ẹ̀kọ́ onípò àkọ́kọ́ | *Yoruba language course*<br>*first degree* |
| ẹnu-ọ̀nà àbáwọlé | *entrance* |
| ìbàmú pẹ̀lú òfin ilé-ìwé | *in accordance with university rules* |
| igba ènìyàn | *200 people* |
| ilé aláràbarà | *house with designs* |
| Ilé-ẹ̀kọ́ọ sẹ́kọ́ńdìrì àgbà | *Senior Secondary School (SSS)* |
| Ilé-ẹ̀kọ́ọ sẹ́kọ́ńdìrì kékeré | *Junior Secondary School (JSS)* |
| ilé-ìfowópamọ́sí | *bank* |
| ilé gogoro | *tall building/tower* |
| Ilé-ẹ̀kọ́ alákọ̀ọ́bẹ̀rẹ̀ | *primary/ elementary school* |
| ilé- ẹ̀kọ́ọ sẹ́kọ́ńdìrì | *secondary school (high school)* |
| ìmọ̀ iṣẹ́ àgbẹ̀ | *agricultural science/farming* |
| iṣẹ́-ọnà aláràbarà | *artistic work* |
| ìwádìí ìjìnlẹ̀ | *research* |
| kíláàsìi sáyẹ́ǹsì<br>lẹ́kíṣọ́ tiatà | *science class*<br>*lecture theater* |
| odidi ọdún mẹ́fà | *a whole/ good six years* |
| oyè ìmọ̀ ìjìnlẹ̀ | *Ph.D* |
| ọgbà àwọn ẹranko | *zoo* |
| ọgbàa yunifásítì/kámpọ́ọ̀sì | *university campus/campus* |
| Ọba'bìrin Èlísábẹ́ẹ̀tì | *Queen Elizabeth* |
| ọmọ ilé-ẹ̀kọ́<br>yàrá ìgbẹ̀kọ́ | *student*<br>*classroom* |
| tiatà ìdánilẹ́kọ̀ọ́ | *lecture theatre* |
| Yunifásítì ti àgíríìkì/ ìmọ̀ iṣẹ́ àgbẹ̀ | *University of Agriculture* |
| Yunifásítì ti tẹkinọ́lọ́jì/ ìmọ̀-ẹ̀rọ | *University of Technology* |

## Verbs

| | |
|---|---|
| jọrọ̀ | *to enjoy the benefits* |
| pegedé | *to succeed* |
| rántí | *to remember* |
| retí | *to expect* |

 CC – 2012 The University of Texas at Austin

| | |
|---|---|
| rojọ́/ wíjọ́ | *to complain* |
| rọ́jú | *to hang in there* |
| tán | *to end* |
| yàtọ̀ | *different* |
| yìn | *to praise* |

## Verb Phrases

| | |
|---|---|
| (dá)_sílẹ̀ | *establish* |
| dojú kọ | *to be faced with* |
| fi ọ̀rọ̀ jomi toro ọ̀rọ̀ | *discuss/ deliberate* |
| gba ìgbéga | *to be promoted* |
| kò rọrùn | *not easy* |
| kú iṣẹ́ | *well done!* |
| má ṣèyọnu | *don't worry/never mind* |
| múra sí ẹ̀kọ́ | *be more studious* |
| ri dájú wipe | *ensure that* |
| ṣe kí n ri ẹ | *show what you can do* |
| wọ̀ ___ lọ́rùn | *to be overwhelmed* |

## Adjectives

| | |
|---|---|
| gbámúṣé<br>láìpẹ́ | *very good/very nice*<br>*very soon* |
| ní gẹ́lẹ́ | *as soon as* |

## Adverb

| | |
|---|---|
| káàkiri | *all around/everywhere* |

## Other Expressions

| | |
|---|---|
| já fáfá | *smart* |
| tí ó tóbi | *that is big* |
| tó mòye | *that are knowledgeable* |
| tó ń gbowó rẹpẹtẹ | *making big bucks* |
| wò ó! | *hey, you see…!* |

 CC – 2012 The University of Texas at Austin

# Lesson 1 - Ẹ̀kọ́ Kìíní:
## Ilé-Ìwé *(School System)*

Ní ilẹ̀ẹ Yorùbá, àwọn ọmọ máa ń bẹ̀rẹ̀ sí lọ sí ilé-ẹ̀kọ́ láti bí ọdún mẹ́fà. Ilé-ẹ̀kọ́ alákọ̀ọ́bẹ̀rẹ̀ ni àwọn òbí máa ń kọ́kọ́ fi ọmọọ wọn sí. Ní ilé-ẹ̀kọ́ alákọ̀ọ́bẹ̀rẹ̀, oríṣiríṣi ẹ̀kọ́ ni àwọn olùkọ́ máa ń kọ́ àwọn ọmọ. Ẹ̀kọ́ bí ẹ̀kọ́ èdèe Yorùbá àti èdè Òyìnbó. Àkọ́sórí tún wà lára ẹ̀kọ̀ tí àwọn ọmọ ilé-ẹ̀kọ́ alákọ̀ọ́bẹ̀rẹ̀ máa ń kọ. Àwọn àkọ́sórí yìí jẹ́ ọ̀nà tí àwọn olùkọ́ máa ń gbà láti fi jẹ́ kí àwọn ọmọ ilé-ìwé mọ ọ̀nà tí ènìyàn máa ń gbà láti rántí nǹkan. Odindi ọdún mẹ́fà ni àwọn ọmọ máa ń lò ní ilé-ẹ̀kọ́ alákọ̀ọ́bẹ̀rẹ̀ kí wọ́n tó lọ sí ilé-ìwé mẹ́fà.

Ní ilé-ẹ̀kọ́ọ sẹ́kọ́ńdìrì, àwọn akẹ́kọ̀ọ́ ní àyè láti mú kíláàsì tí wọ́n bá fẹ́. Àwọn ọmọ ilé-ẹ̀kọ́ tí wọ́n fẹ́ràn ìṣirò ló máa ń lọ kíláàsì sáyẹ́ǹsì. Àwọn tí ó bá fẹ́ràn lítíréṣọ̀ ni wọ́n máa ń lọ sí áàtì. Oríṣiríṣi ìdánwò ni àwọn akẹ́kọ̀ọ́ máa ń ṣe láti gba ìgbéga láti kíláàsì kan sí ìkejì. Apá méjì ni ẹ̀kọ́ọ sẹ́kọ́ńdìrì pínsí. Apá alákọ̀ọ́kọ́ ni sẹ́kọ́ńdìrì kékeré, ti ẹlẹ́ẹ̀kejì ni sẹ́kọ́ńdìrì àgbà. Ọdún mẹ́ta mẹ́ta ni akẹ́kọ̀ọ́ ń lò ní apá kọ̀ọ̀kan. Apá kejì jẹ́ ti àwọn àgbà. Lẹ́yìn ọ̀dún mẹ́fà ni ilé-ẹ̀kọ́ọ sẹ́kọ́ńdìrì . Àwọn akẹ́kọ̀ọ́ tí ó bá pegedé ni wọ́n ní àǹfààní láti tẹ̀síwájú nínúu ẹ̀kọ́ọ wọn.

Ilé-ẹ̀kọ́ gíga ni ó tẹ̀lé ilé-ẹ̀kọ́ọ sẹ́kọ́ńdìrì. Oríṣiríṣi ilé-ìwé gíga ni ó wà. Àwọn èyí tí ó wà fún àwọn tí ó kọ́ nípà ìmọ̀ ẹ̀kọ́ yàtọ̀ sí àwọn èyí tí ó wà nípa ìṣẹ́ ọwọ́. Ilé-ẹ̀kọ́ gíga kan tún wa tí wọ́n ń pè ni ilé ẹ̀kọ́ọ gbogbo-ǹ-ṣe tí a tún máa jẹ́ politẹ́kíníìkì. Nínúu gbogbo ilé-ẹ̀kọ́ gíga, ti yunifásítì ni ó ga jù. Àwọn tí ó bá fẹ́ di dókítà, àdajọ́, ọ̀mọ̀wé àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ ni ó máa ń lọ sí yunifásítì. Yunifásítì tún pín sí ọ̀nà oríṣiríṣi. Yunifásítì tí ó wà fún ìmọ̀ iṣẹ́ àgbẹ̀ ni wọ́n ń pè ní Yunifásítì ti àgíríìkì. Èyí tí ó wà fún ìmọ̀-ẹ̀rọ ní wọ́n ń pè ní Yunifásítì ti tẹkinọ́lọ́jì.

## Iṣẹ́ Ṣíṣe 1

Dáhùn àwọn ìbéèrè wọ̀nyí ní ẹ̀kúnrẹ́rẹ́.
*Answer the following questions in complete sentences.*

1. Àti ọmọ ọdún mélòó ni àwọn ọmọ ti máa ń bẹ̀rẹ̀ ilé-ìwé lílọ ní ilẹ̀ẹ Yorùbá?
2. Báwo ni àwọn olùkọ́ ilé-ẹ̀kọ́ alákọ̀ọ́bẹ̀rẹ̀ ṣe máa ń ran àwọn akẹ́kọ̀ọ́ lọ́wọ́ láti le rántí nǹkan?
3. Ilé-ìwé wo ló tẹ̀lé ilé-ìwé alákọ̀ọ́bẹ̀rẹ̀?
4. Irú kíláàsì wo ni àwọn akẹ́kọ̀ọ́ tí wọ́n fẹ́ràn lítíréṣọ̀ máa ń lọ ni ilé-ẹ̀kọ́ọ sẹ́kọ́ńdìrì?
5. Ilé-ẹ̀kọ́ wo ni ó ga jùlọ nínú ètò ẹ̀kọ́ ni ilẹ̀ẹ Yorùbá?

 CC – 2012 The University of Texas at Austin

## Iṣẹ́ Ṣíṣe 2

So àwọn ọ̀rọ̀ tí ó bara mu ni ọ̀wọ́ A àti ọ̀wọ́ B papọ̀.
*Match the words in column A with those in column B.*

| A | B |
|---|---|
| onímọ̀-ẹ̀rọ | memory verse |
| èdè | math |
| àkọ́sórí | arts |
| ìṣirò | language |
| áàtì | engineer |
| ìdánwò | experiment |
| adájọ́ | engineering |
| oníròyìn | judge |
| ìmọ̀-ẹ̀rọ | examination |
| àyẹ̀wò | journalist |

## Iṣẹ́ Ṣíṣe 3

Kọ ìtumọ̀ àwọn ọ̀rọ̀ wọ̀nyí sílẹ̀ ní èdèe Yorùbá.
*Write the meanings of these words in Yorùbá.*

1. àkọ́sórí
2. ilé-ẹ̀kọ́ alákọ̀ọ́bẹ̀rẹ̀
3. oníròyìn
4. ìmọ̀-ẹ̀rọ
5. àyè


CC – 2012 The University of Texas at Austin

## Iṣẹ́ Ṣíṣe 4

Parí àwọn gbólóhùn wọ̀nyí.
*Complete the following sentences.*

1. Ní ilẹ̀ẹ Yorùbá, àwọn ọmọ máa ń bẹ̀rẹ̀ sí lọ sí ilé-ẹ̀kọ́ láti bí ọdún mélòó?
   a. méjì
   b. mẹ́ta
   c. márùn-ún
   d. mẹ́rin

2. Ọdún mélòó ni àwọn ọmọ máa ń lò ní ilé-ìwé alákọ̀ọ́bẹ̀rẹ̀ kí wọ́n tó lọ sí ilé-ẹ̀kọ́ọ sẹ́kọ́ńdìrì ?
   a. márùn-ún
   b. mẹ́fà
   c. mẹ́rin
   d. méje

3. Oríṣiríṣi apá mélòó ni ilé-ẹ̀kọ́ọ sẹ́kọ́ńdìrì pín sí?
   a. mẹ́ta
   b. mẹ́rin
   c. méjì
   d. márùn-ún

4. Ilè-ẹ̀kọ́ gíga tí ó ga jù ni?
   a. Politẹ́kíníìkì
   b. Yunifásítì
   c. Ilé-ẹ̀kọ́ọ sẹ́kọ́ńdìrì
   d. Ilé-ẹ̀kọ́ gíga olùkọ́ni

5. Àwọn tí ó bá fẹ́ di ______________ ni wọ́n máa ń lọ sí Yunifásítì.
   a. olùkọ́
   b. dókítà
   c. aránṣọ
   d. aránbàtà

## Iṣẹ́ Ṣíṣe 5

Kí ni èròò rẹ nípa ẹ̀kọ́ kíkọ́ láàárín àwọn Yorùbá àti àwọn ará oríl̀ẹ̀-èdèè rẹ?

 CC – 2012 The University of Texas at Austin

## Lesson 2 - Ẹ̀kọ́ Kejì:
## University Course Schedules

### Ìsọ̀rọ̀ngbèsì *(Dialogue)*

Tádé àti Bùsọ́lá ń sọ̀rọ̀ nípa kíláàsì wọn ní Yunifásítì ti Texas ní Austin. Tádé ń kẹ́kọ̀ọ́ láti gba oyè nínú ìmọ̀-ẹ̀rọ. Bùsọ́lá ń kọ́ ẹ̀kọ́ ìròyìn. Ó fẹ́ di oníròyìn tí ó bá parí ẹ̀kọ́ọ rẹ̀. Ọdún kẹtaa Tádé àti Bùsọ́lá nìyí ní ilé-ẹ̀kọ́ gíga. Wọ́n pàdé ni ìpàdé ẹgbẹ́ ọmọ Áfíríkà (ASA – African Students Association). Àwọn méjéèjì fi ọ̀rọ̀ jomitooro ọ̀rọ̀ nípa ìṣòro tí wọ́n ń dojú kọ nínú ẹ̀kọ́ọ wọn.



| | |
|---|---|
| **Bùsọ́lá:** | Tádé, ǹjẹ́ o mọ̀ pé kíláàsì márùnún ni mo ní ni simẹ́sítà yìí? |
| **Tádé:** | Háà! Hun ùn. Tìrẹ mà dára à. Kíláàsì márùnún ni èmi náà ni, pẹ̀lú láàbù. Mò ń ṣe kákúlọ́ọ̀sì, físíìsì, ẹ̀kọ́ èdèe Yorùbá, kẹ́mísírì àti sitatísíìkì. Iṣẹ́ náà wọ̀ mí lọ́rùn nítorí pe ojoojúmọ́ ni mo máa ń lọ sí láàbù. Mo ń ṣe àyẹ̀wò kan lọ́wọ́ nísinsìnyí fún ìdánwò. N kò sì mọ bí mo ti máa rí kẹ́míkà tí màá lò pẹ̀lú àyẹ̀wò náà láti fi rí èsì tí mò ń retí nínú àyẹ̀wò náà. |
| **Bùsọ́lá:** | Háà! Mo yìn ẹ́ o. Iṣẹ́ ńlá ni ò ń ṣe. Èmi kò ní láàbù, bẹ́ẹ̀ ni n kò sì ní iṣẹ́ ojoojúmọ́. Nítorí náà kò yẹ kí n máa rojọ́. Kú isẹ́ o, Tádé. |
| **Tádé:** | O o, O ṣé o. Wò ó, níṣe ni mo ń retí kí simẹ́sítà yìí tán o jàre. |
| **Bùsọ́lá:** | Má ṣè ìyọnu Tádé, gbogbo rẹ̀ ti ń tán lọ. Láìpẹ́ ìwọ náà yóò di ẹnjíníà tó |

| | |
|---|---|
| | mòye, tó ń gbówó rẹpẹtẹ. |
| **Tádé:** | Lóòótọ́ ni o sọ Bùsọ́lá, ṣùgbọ́n kíkẹ́kọ̀ọ́ gboyè ẹnjíníà kò rọrùn rárá. |
| **Bùsọ́lá:** | Tádé, má sọ bẹ́ẹ̀ mọ́. Kò sí ẹ̀kọ́ ìwé kankan tí ó rọrùn rárá. Ṣùgbọ́n tí ènìyàn báá rọ́jú, ènìyàn á jọrọ̀ọ rẹ̀. |
| **Tádé:** | Otítọ́ ni ọ̀rọ̀ọ rẹ o, Bùsọ́lá. Mo ti gbọ́ ohun tí o sọ. Màá rọ́jú. |
| **Bùsọ́lá:** | Ó dára bẹ́ẹ̀. Jẹ́ kí n kọ́ ẹ lórin tí bàbáa mi máa ń kọ láti gbàwá níyànjú kí a ba à lè múra sí ẹ̀kọ́ọ wa.<br><br>Bàtà rẹ á dún ko ko kà<br>Bàtà rẹ á dún ko ko kà<br>Bí o bá kàwé rẹ, bàtà rẹ á dún ko ko kà<br>Bùsọ́lá kàwé rẹ, bàtà rẹ á dún ko ko kà<br>Tádé kàwé rẹ, bàtà rẹ á dún ko ko kà<br>Bàtà rẹ á wọ́ ṣẹrẹrẹ nílẹ̀ o<br>Bàtà rẹ á wọ́ ṣẹrẹrẹ nílẹ̀ o<br>Bí o ò bá kàwé rẹ bàtà rẹ á wọ́ ṣẹrẹrẹ nílẹ̀. |
| **Tádé:** | Háà! Bùsọ́lá, O ti fún mi ní agbára ọ̀tun láti kàwé síi. |
| **Bùsọ́lá:** | Ó dára o, alágbára ìwé. |

## Iṣẹ́ Ṣíṣe 1

Sọ **bẹ́ẹ̀ ni** tàbí **bẹ́ẹ̀ kọ́** sí àwọn gbólóhùn wọ̀nyìí
*State whether the following sentences are **true** or **false***

| | BẸ́Ẹ̀ NI | BẸ́Ẹ̀ KỌ́ |
|---|---|---|
| 1. Tádé àti Bùsọ́lá ń sọ̀rọ̀ nípa iṣẹ́ oko. | ☐ | ☐ |
| 2. Ọmọ ẹgbẹ́ kan náà ni àwọn méjèèjì. | ☐ | ☐ |
| 3. Kíláàsì Bùsọ́lá pọ̀ ju ti Tádé lọ. | ☐ | ☐ |
| 4. Tádé ní iṣẹ́ẹ láàbù lójojúmọ́. | ☐ | ☐ |
| 5. Ẹ̀kọ́ nípa ìmọ̀-ẹ̀rọ ni Tádé ń kọ́. | ☐ | ☐ |
| 6. Bùsọ́lá ń gba Tádé níyànjú pé kí ó má ṣàárẹ̀ nípa iṣẹ́ẹ rẹ̀. | ☐ | ☐ |
| 7. Bùsọ́lá fẹ́ di oníròyìn. | ☐ | ☐ |
| 8. Láti kẹ́kọ̀ọ́ gboyèe ẹnjínìa rọrùn púpọ̀. | ☐ | ☐ |
| 9. Bùsọ́lá kọ orin fún Tádé láti mú u lọ́kàn le. | ☐ | ☐ |
| 10. Orin náà dára púpọ̀. | ☐ | ☐ |

 CC – 2012 The University of Texas at Austin

## Iṣẹ́ Ṣíṣe 2

Parí àwọn gbólóhùn wọ̀nyí.
*Complete the following sentences.*

1. ________________ ni Tádé àti Bùsọ́lá?
   a. Ọ̀tá
   b. Ọmọ ìyá
   c. Ọ̀rẹ́
   d. Ẹbí

2. Bùsọ́lá fẹ́ di ______________ ní ẹ̀yìn ọ̀la?
   a. alákọ̀wèé
   b. àgbẹ̀
   c. oníròyìn
   d. agbẹjọ́rò

3. ________________ ni Tádé nífẹ̀ẹ́ láti dà?
   a. Oníròyìn
   b. Agbẹjọ́rò
   c. Ẹnjiníà
   d. Alákọ̀wèé

4. Kíláàsì _______________ ni Bùsọ́lá ní ni simẹ́sítà yìí?
   a. mẹ́fà
   b. méjì
   c. mẹ́rin
   d. márùn–ún

5. _______________ jẹ́ ọ̀kan lára iṣẹ́ tí Tádé ń ṣe?
   a. Bàọ̀lọ́jì
   b. Ẹ̀kọ́ èdèe Yorùbá
   c. Kẹ́mísírì
   d. Kákúlọ́ọ̀sì

 CC – 2012 The University of Texas at Austin

## Iṣẹ́ Ṣíṣe 3

Ṣàlàyé orin yìí ní èdèe Yorùbá gẹ́gẹ́ bí o ṣe rí i kà nínú àyọkà òkè yìí.
*Explain this song in Yorùbá based on what you have read in the passage above.*

Bàtà rẹ á dún ko ko kà
Bàtà rẹ á dún ko ko kà
Bí o bá kàwé rẹ, bàtà rẹ á dún ko ko kà
Bùsọ́lá kàwé rẹ, bàtà rẹ á dún ko ko kà
Tádé kàwé rẹ, bàtà rẹ á dún ko ko kà
Bàtà rẹ á wó ṣẹrẹrẹ nílẹ̀ o
Bàtà rẹ á wó ṣẹrẹrẹ nílẹ̀ o
Bí o ò bá kàwé rẹ bàtà rẹ á wọ́ ṣẹrẹrẹ nílẹ̀.

## Iṣẹ́ Ṣíṣe 4

Sọ fún wa nípa ilé-ẹ̀kọ́ọ̀ rẹ tàbí yunifásítìì rẹ.
*Tell us about your school or your university.*

## Iṣẹ́ Ṣíṣe 5

Kọ ìtumọ̀ àwọn ọ̀rọ̀ wọ̀nyí sílẹ̀ ní èdèe Yorùbá.
*Provide the meaning of the following words in Yorùbá.*

1. oníròyìn
2. àyẹ̀wò
3. ìpàdé ẹgbẹ́
4. jomitooro
5. gbà níyànjú

 CC – 2012 The University of Texas at Austin

# Lesson 3 - Ẹ̀kọ́ Kẹta: Facilities




## Yunifásítì ti Ìbàdàn

Oríṣiríṣi Yunifásítì ni ó wà ní orílẹ̀-èdè Nàìjíríà. Ọ̀kan pàtàkì ni Yunifásítì ti Ìbàdàn ní ìlú Ìbàdàn ní ìpínlẹ̀ Ọ̀yọ́. Òhun ni Yunifásítì àkọ́kọ́ ní orílẹ̀-èdèe Nàìjíríà. Àwọn Òyìnbó aláwọ̀ funfun ni wọ́n dá a sílẹ̀ ní ọdúnun 1948 bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé wọ́n yí orúkọ rẹ̀ padà sí Yunifásítì ti Ìbàdàn lẹ́yìn ìgbà tí orílẹ̀-èdèe Nàìjíríà gba òmìnira ní ọdúnun 1960.

Gbogbo ọ̀nà ni ó wọ Yunifásítì ti Ìbàdàn. Bí ènìyàn bá ń bọ̀ láti agbègbèe Sángo, ní gẹ́lẹ́ tí ènìyàn bá ti dé iwájúu Yunifásítì yìí ni ènìyàn á ti rí ẹnu-ọ̀nà àbáwọlé sí ilé-ẹ̀kọ́ gíga yìí pẹ̀lú iṣẹ́-ọnà aláràbarà. Ọ̀pópónà méjì ni ènìyàn á rí ní kété tí ènìyàn bá ti wọlé: ọ̀kan fún àwọn tí ó

 CC – 2012 The University of Texas at Austin

ń lọ sí inú ọgbà ilé-ìwé yìí nígbà tí ìkejì dúró fún àwọn tí wọ́n bá ń jade kúrò nínú ilé-ìwé yìí.

Ilé gogoro ní ibi tí aago ti ó ń ka wákàtí àti ìṣẹ́jú ni ènìyàn á kọ́kọ́ rí tí ènìyàn bá ti wọ inú ọgbà ilé-ìwé yìí tí ènìyàn bá rìn síwájú díẹ̀. Nínú ilé tí ó wà ní tòsí ilé gogoro yìí, tíí ṣe ibùjókòó àwọn alákòóso ọgbà ni gbogbo àṣẹ àti òfin ti ń wá. Oríṣiríṣi ẹ̀kọ́ ni wọ́n ń kọ́ àwọn akẹ́kọ̀ọ́ ní Yunifásítì ti Ìbàdàn. Nínúu wọn ni ẹ̀kọ́ onípò àkọ́kọ́ tí amọ̀ sí BÍ-EÈ, BÍ-Ẹ̀ẸDÌ, BÍ-ẸẸ̀SIÌ àti àwọn onípele ńlá tí ń jẹ́ Ẹ́M-EÈ, Ẹ́M-ẸẸ̀DÌ, Ẹ́M-ẸẸ̀SÌ, títí dé àwọn oyè imọ̀ ìjìnlẹ̀ tí wọ́n ń pè ní Ph.D.

Oríṣiríṣi ẹ̀ka ẹ̀kọ́ ni ó wà nínú ọgbàa Yunifásítì ti Ìbàdàn. Láraa wọn ni a ti rí ẹ̀ka ẹ̀kọ́ olùkọ́ni, ẹ̀ka ẹ̀kọ́ iṣẹ́ àgbẹ̀, ẹ̀ka ẹ̀kọ́ iṣẹ́ ọnà àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Nínú ọgbàa Yunifásítì ti Ìbàdàn, oríṣiríṣI ibùgbé tí a mọ́ sí ọ́ọ̀lù ni ó wà fún àwọn akẹ́kọ̀ọ́ láti gbé. Àti ọkùnrin àti obìnrin ni wọ́n ní àǹfààní láti gbé inú ọ́ọ̀lù wọ̀nyí. Ọ̀ọ̀lù Ọbabìnrin Èlísábẹ́ẹ̀tì àti Ídíá ni ti àwọn obìnrin, Nnamdi Azikiwe, Kùtì, Mellanby àti àwọn yòókù ni ti àwọn ọkùnrin nígbà tí Tafawa Balewa jẹ́ ọ̀kan lára ti àwọn akẹ́kọ̀ọ́ onípele tó gajù.

Ṣé àwọn àgbà bọ̀ wọ́n ní b'ọ́mọ bá ṣe iṣẹ́ déédé, ó yẹ kí ó ní àsìkò àti ṣeré. Èyí túmọ̀ sí pé lẹ́yìn iṣẹ́ òòjọ́, àsìkò yẹ kó wà fún ìdárayá. Pápá ìṣeré wà nínú ọgbà Yunifásítì ti Ìbàdàn fún bọ́ọ̀lù àfẹsẹ̀gbá, bọ́ọ̀lù àfọwọgbá àti bọ́ọ̀lù àjùsáwọ̀n. Bẹ́ẹ̀ náà ni ọgbà àwọn ẹranko níbi tí a ti lè rí ejò, kìnìún, ọ̀bọ, ìjàpá, ẹyẹ lóríṣiríṣi àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ wà nínúu ọgbà Yunifásítì ti Ìbàdàn. Ọgbà ilé-ìwée Yunifásítì ti Ìbàdàn tóbi ká má parọ́. Èyí ló jẹ́ kí n gbà pé àkọ́dá gan-an ni ní tòótọ́.

## Iṣẹ́ Ṣíṣe 1

Dáhùn àwọn ìbéèrè wọ̀nyí ní ẹ̀kúnrẹ́rẹ́.

*Answer the following questions in complete sentences.*

1. Àwọn wo ni wọ́n dá Yunifásítì ti Ìbàdàn sílẹ̀?
2. Nígbà wo ni wọ́n dá Yunifásítì ti Ìbàdàn sílẹ̀?
3. Ní ilù wo àti ìpínlẹ̀ wo ni Yunifásítì ti Ìbàdàn wà?
4. Kí ni orúkọ òpópónà tí a lè gbá wọ inú ọgbà Yunifásítì ti Ìbàdàn?
5. Níbo ni àṣẹ àti òfin ilé-ìwé yìí ti ń wá?

 CC – 2012 The University of Texas at Austin

## Iṣẹ́ Ṣíṣe 2

Parí àwọn gbólóhùn wọ̀nyí.

*Complete the following sentences.*

1. Orúkọ ọ́ọ̀lù mélóò ni a dá nínúu àyọkà òkè yìí?
   a. méjì
   b. mẹ́fà
   c. mẹ́rin
   d. mẹ́tàlá

2. _____________ kò sí nínú àwọn ọ̀ọ́lù tí a le rí nínú ọgbàa Yunifásítì ti Ìbàdàn?
   a. Ọ́ọ̀lù Ọbabìnrin Èlísábẹ́ẹ̀tì
   b. Ọ́ọ̀lùu Nnamdi Azikiwe
   c. Ọ́ọ̀lùu Mọ́remí

3. Ẹ̀ka ẹ̀kọ́ mélóò ni a dárúkọ lára àwọn ẹ̀ka ẹ̀kọ́ tí ó wà nínú ọgbàa Yunifásítì ti Ìbàdàn?
   a. mẹ́ta
   b. méjì
   c. mẹ́rin
   d. n kò mọ̀

4. _________________ ni wọ́n yí orúkọ Yunifásítì ti Ìbàdàn padà?
   a. Ní ọdúnun 1960
   b. Ní ọdúnun 1948
   c. Kí ó tó dí 1960
   d. Lẹ́yìn ọdúnun 1960

5. Òpópónà mélóò ni ó wọ inú ọgbàa Yunifásítì ti Ìbàdàn?
   a. mẹ́ta
   b. méjì
   c. mẹ́rin
   d. mẹ́tàlá

 CC – 2012 The University of Texas at Austin

## Ọ̀rọ̀ àdáṣọ *(Monologue)*

**Túndé ń sọ̀rọ̀ nípa ilé gogoro ni ilé-ìwée rẹ̀**
**(*Túndé is talking about the tallest building at his school.)***



Ọ̀pọ̀lọpọ̀ ilé-ìwé ló wà ní tòótọ̀, àmọ ti ilé-ìwée mi yàtọ̀ gan-an ni. Ilé-ìwée mi yàtọ̀ sí àwọn ilé-ìwé yòókù. Ọ̀rọ̀ mi yìí kọjá àpọ́nlé, bẹ́ẹ̀ kì í ṣe àpọ́nlu. Àwọn Yorùbá ní bí a kò bá dé oko baba ẹlomíràn wò, a kò lè mọ èyí tí ó tóbi jù nínú oko baba ẹni àti baba ẹlomíràn.

Èmi ti dé ilé-ìwé mìíràn, mo sì ti rí i dájú pé àjànàkú kọjá mo ri nǹkan fìrí. Mo ti rí erin, mo sì mọ̀ pé erin ni. Ṣé ti àwọn olùkọ́ tí wọ́n gbámúṣé ni kí n sọ ni tàbí ti àwọn ilé aláràbarà tí wọ́n wà ni kí n wí?

Ká mú t'ẹ̀gàn kúrò, ká tún fi t'ẹ̀gàn kun, ilé-ìwé ni ilé-ìwéè mi. Yunifásítì ti Texas ní Austin ni mò ń sọ. Gbogbo ọ̀nà ni o lè gbà wọ ilé-ìwé mi yìí. Tí o bá wá gba iwájú ilé-ìfowópamọ́sí wọlé, kí o kàn gbé ojú wo ọ̀ọ́kàn, wà á rí ilé gogoro. Gígaa rẹ̀ fẹ́ ẹ̀ lè kan ọrun. Ilé yìí ni wọ́n ń pè ní "UT Tower". Ibẹ̀ gan-an ni gbogbo ètò àti àṣẹ ilé-ìwée mi ti ń wá. Èniyàn kò gbọdọ̀ gbókè wòran rárá. Tí o bá gbìyànjú dé iwájú ilé yìí tàbí tí o ní àǹfààní láti wọ inúu rẹ̀, wà á kí ajé kú ìkàlẹ́. Ilé-ìwéè mi dára t'ẹ̀gan lókù. Ìwọ gbìyànjú kí o wá, ìròyìn kò tó àfojúbà.

 CC – 2012 The University of Texas at Austin

### Iṣẹ́ Ṣíṣe 3

Sọ **bẹ́ẹ̀ ni** tàbí **bẹ́ẹ̀ kọ́** fún àwọn gbólóhùn wọ̀nyìí
*State whether the following sentences are **true** or **false***

| | BẸ́Ẹ̀ NI | BẸ́Ẹ̀ KỌ́ |
|---|---|---|
| 1. Ọmọ ilé-ìwée Yunifásítì ti Texas ní Austin ni Túndé. | ☐ | ☐ |
| 2. Ọ̀nà kan ló wọ ilé-ìwée Túndé. | ☐ | ☐ |
| 3. Oko bàbáa Túndé ni Túndé ń ṣàlàyé. | ☐ | ☐ |
| 4. Texas ni ilé-ìwée Túndé wà. | ☐ | ☐ |
| 5. Àwọn olùkọ ilé-ìwée Túndé kò mọ nǹkan kan. | ☐ | ☐ |

### Iṣẹ́ Ṣíṣe 4

Kọ ìtumọ̀ àwọn ọ̀rọ̀ wọ̀nyí sílẹ̀ ní èdèe Yorùbá.
*Write the meaning of the following words in Yorùbá.*

1. àpọ́nlé
2. àpọ́nlu
3. àjànàkú
4. gbámúṣé
5. ilé aláràbarà
6. ẹ̀gàn
7. ilé-ìfowópamọ́sí
8. ilé gogoro
9. ìyànjú
10. àfojúbà

### Iṣẹ́ Ṣíṣe 5

Ó kàn ẹ́, sọ nípa ilé-ìwé rẹ fún wa.
*Now it's your turn, tell us about your school.*


CC – 2012 The University of Texas at Austin

# Lesson 4 - Ẹ̀kọ́ Kẹrin: Campus Life

Oríṣiríṣi Yunifásítì ni ó wà ni ílẹ̀ẹ Yorùbá. Nínúu wọn ni Yunifásítì ìmọ̀-ẹ̀rọ, ìmọ̀ olùkọ́ni, ìmọ̀ àgbẹ̀ àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Ọ̀jọ̀gbọ́n ni orúkọ̀ tí wọ́n ń pe àwọn olùkọ́ ilé-ẹ̀kọ́ Yunifásítì. Iṣẹ́ẹ wọn ni láti kọ́ àwọn ọmọ ilé-ẹ̀kọ́ àti láti rí i dájú wí pé wọ́n ṣe iṣẹ́ẹ wọ̀n ní ìbámú pẹ̀lú òfin ilé-ẹ̀kọ́.

Yàrá ìgbẹ̀kọ́ ńlá ni wọ́n ń pè ní tiatà ìdánilẹ́kọ̀ọ́. Àwọn lẹ́kísọ̀ tiatà tí ó tóbi lè gba igba ènìyàn. Gbogbo ẹka-ẹ̀kọ́ ni ó ní tíátà ìdánilẹ́kọ̀ọ́ọ tirẹ̀. Àwọn yàrá ìkàwé kéékèèké tún wà káàkiri ọgbà ilé-ẹ̀kọ́. Àwọn ẹ̀ka ẹ̀kọ́ọ sáyẹ́nsì máa ń ní yàrá ìmọ̀ ìwádìí ìjìnlẹ̀. Ẹ̀ka àṣà àti ìjó ni gbọ̀ngán ìdárayá. Nínúu gbọ̀ngán ìdárayá ni wọ́n ti máa ń ṣe ìdánwò ṣe-é-kí-ń-rí-ẹ. Àwọ́n ọmọ ilé- ẹ̀kọ́ ní àyè láti wo eré àti ijó nínúu gbọ̀ngán ìdárayá.

Ibùgbé àwọn ọmọ ilé-ìwé ni wọ́n ń pè ní ọ́ọ̀lù. Ọ́ọ̀lù tàbí ósítẹ̀lì àwọn ọkùnrin yàtọ̀ sí ti àwọn obìnrin. Púpọ̀ nínúu àwọn ọ́ọ̀lù yìí ni wọ́n dá sílẹ̀ pẹ̀lú orúkọ àwọn ènìyàn pàtàkì ní àwùjọ. Ọ́ọ̀lù púpọ̀ ni ó wà ní ilé-ẹ̀kọ́ọ Yunifásítì ti Ìbàdàn. Díẹ̀ nínúu àwọn ọ́ọ̀lù yìí ni Ọ́ọ̀lu Ọbabìrin Èlísábẹ́ẹ̀tì, Kútì, Awólọ́wọ̀, Mellanby àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Àwọn olùdarí ọ́ọ̀lù kì í jẹ́ kí ọkùnrin wọ ọ́ọ̀lù àwọn obìnrin láti àárọ̀ títí di agogo mẹ́rin. Àwọn alámójútó ọ́ọ̀lù ní láti rí i wí pé àyíká ọ́ọ̀lù mọ́ tónítóní.

Àwọn ibùgbé aládàáni wà káàkiri agbègbè ibi tí Yunifásítì bá wà. Àwọn ti aládàáni máa ń wọ́n ju tí ìjọba lọ. Àwọn ènìyàn lè wọ ibùgbé ti aládàáni ní àsìkò tí ó bá wù wọ́n.

Aṣọ oríṣiríṣi ni àwọn ọmọ Yunifásítì máa ń wọ̀. Wọ́n lè wọ aṣọ òyìnbó, wọ́n sí tún lè wọ ti ìbílẹ̀. Púpọ́ nínú àwọn obìnrin ní ilé-ẹ̀kọ́ gíga Yunifásitì ni wọ́n máa ń wọ ṣòkòtò. Àwọn ọmọ ilé-ẹ̀kọ̀ gíga kì í sáábà rayè dáná. Nítorí ìdí èyí ni púpọ̀ nínúu wọn ṣe máa ń lọ sí kàǹtíìnì láti lọ ra oúnjẹ jẹ. Yàtọ̀ sí ẹ̀kọ́ ìwé, oríṣiríṣi ẹ̀kọ́ ni àwọn ọmọ máa ń kọ́ ní ilé-ẹ̀kọ̀ gíga Yunifásítì. Ìdi nìyí tí ó fi jẹ́ pe ọmọ ní láti já fáfá tí ó bá fẹ́ wọ yunifásítì. Bí bẹ́ẹ̀ kọ́ irú ọmọ bẹ́ẹ̀ yóò dojú kọ ìṣòro láti ọ̀dọ̀ àwọn olùkọ́ àti àwọn akẹ́gbẹ́ẹ rẹ̀ ní ilé-ẹ̀kọ́.

Ilé-ìwé gíga ti Yunifásítì gbayì láàárín àwọn Yorùbá. Gbogbo àwọn òbí ní wọ́n sì máa ń fẹ́ kí ọmọ wọn lọ sí ibẹ̀. Tí ọmọ bá kàwé gboyè ni ilé-ẹ̀kọ́ gíga, iyì àti oríire ńlá ni fún àwọn òbí. Nítorí náà ni àwọn Yorùbá ṣe máa ń kọrin pé:

> Yunifásítì dára níbi táwọn ọ̀jọ̀gbọ́n wà
> Ìbẹ̀ lọ́mọ́ mi yó lọ
> Olúwa yó mú un débẹ̀ o.

## Iṣẹ́ Ṣíṣe 1

Dáhùn àwọn ìbéèrè wọ̀nyí ní ẹ̀kúnrẹ́rẹ́.
*Answer the following questions in complete sentences.*

1. Oríṣi Yunifásítì mélòó ni a dárúkọ nínú àyọkà yìí?
2. Kí ni orúkọ tí wọ́n ń pe àwọn olùkọ́ ní Yunifásítì?
3. Dárúkọ àwọn ọ́ọ̀lù tí o rí nínúu àyọkà yìí.
4. Ǹjẹ́ o rò pé ààyè wà fún àwọn akẹ́kọ̀ọ́ láti ṣe ohun tí ó bá wù wọ́n ní Yunifásítì? Ṣe àlàyé.
5. Kí ni àwọn àǹfààní tí ó wà nínúu kí ènìyàn lọ sí Yunifásítì?

## Iṣẹ́ Ṣíṣe 2

Sọ **bẹ́ẹ̀ ni** tàbí **bẹ́ẹ̀ kọ́** sí àwọn gbólóhùn wọ̀nyí.
*State whether the following sentences are **true** or f**alse**.*

| | BẸ́Ẹ̀ NI | BẸ́Ẹ̀ KỌ́ |
|---|---|---|
| 1. Yunifásítì dára láti lọ. | ☐ | ☐ |
| 2. O dára kí ọmọ já fáfá kí ó tó bẹ̀rẹ̀ẹ Yunifásítì. | ☐ | ☐ |
| 3. Kò pọn dandan kí ọmọ lọ sí ilé-ẹ̀kọ́ alákọ̀ọ́bẹ̀rẹ̀ kí ó tó lọ sì Yunifásítì. | ☐ | ☐ |
| 4. Iṣẹ́ àwọn Ọ̀jọ́gbọ́n ní Yunifásítì ni láti rí i pé akẹ́kọ̀ọ́ gbáradì fún ìdánwò. | ☐ | ☐ |
| 5. Àwọn òbí kò fẹ́ran kí ọmọ wọ́n lọ sí Yunifásítì. | ☐ | ☐ |

## Iṣẹ́ Ṣíṣe 3

Ó kàn ẹ́, sọ fún wa nípa yàrá tí ò ń gbé.
*Now it's your turn. Tell us about your room.*

 CC – 2012 The University of Texas at Austin

### Iṣẹ́ Ṣíṣe 4

Parí àwọn gbólóhùn wọ̀nyí.
*Complete the following questions.*

Gẹ́gẹ́ bí mo ṣe rí i kà nínú àyọkà òkè yìí ____________ jẹ́ ibi tí àwọn akẹ́kọ̀ọ́ ti ń kọ́ ẹ̀kọ́. ____________ ni orúkọ ibi tí wọ́n ń gbe. Àwọn akẹ́kọ̀ọ́ máa ń lọ jẹun ní ____________tí ebi bá ń pa wọ́n. Oríṣi aṣọ ____________ ni wọ́n máa ń wọ̀. Àwọn obìnrin tilẹ̀ máa ń wọ ____________ nígbá mìíràn.

### Iṣẹ́ Ṣíṣe 5

Ṣàlàyé orin yìí ní èdèe Yorùbá gẹ́gẹ́ bí o ṣe rí i kà nínú àyọkà òkè yìí.
*Explain this song in Yorùbá based on what you have read in the passage above.*

Yunifásítì dára níbi táwọn ọ̀jọ̀gbọ́n wà
Ìbẹ̀ lọ́mọ́ mi yó lọ
Olúwa yó mú un débẹ̀ o.

 CC – 2012 The University of Texas at Austin

# APPENDIX

## Fáwẹ̀lìi Yorùbá (*Yorùbá Vowels*)

/a/

| | | |
|---|---|---|
| ajá | n. | *dog* |
| ara | n. | *body* |
| àwa | pr. | *we* |
| àpà | n. | *a wasteful person* |
| àlá | n. | *dream* |
| àlọ́ | n. | *riddle* |
| abà | n. | *hut* |
| àrà | n. | *style* |
| àgbára | n. | *strength* |
| àga | n. | *chair* |

**Tone practice:**

| | | |
|---|---|---|
| àpà | n. | *a wasteful person* |
| apá | n. | *arm* |
| àpá | n. | *scar* |

**Tongue twisters:**

Àjàlá jẹ àjẹkùu Jídé.
*Àjàlá ate Jídé's leftovers.*

Adé jẹ ẹjaa Jayé
*Adé ate Jayé's fish.*

/e/

| | | |
|---|---|---|
| ewé | n. | *leaf* |
| *èwe* | n. | *youth* |
| eré | n. | *play, game* |
| erè | n. | *python* |
| edé | n. | *shrimp* |
| èdè | n. | *language* |
| èpè | n. | *curse* |
| pélé | n. | *a type of facial mark* |
| gèlè | n. | *headwear(female)* |
| ètè | n. | *lip* |

**Tone practice:**

| | | |
|---|---|---|
| edé | n. | *shrimp* |
| èdè | n. | *language* |
| eré | n. | *play, game* |
| erè | n. | *python* |
| èrè | n. | *benefit / gain* |
| eruku | n. | *dust* |
| èkuru | n. | *a type of meal made with black eyed peas* |

**Tongue twisters:**

Wíwẹ̀ là á wẹ̀ ká lè jàre ọyẹ́. (Proverb)
*Taking birth prevents one's body from feeling cold.*

Délé dé adé ọba.
*Délé wore the king's crown.*

/ẹ/

| | | |
|---|---|---|
| ẹ̀dá | n. | *human being* |
| kẹ̀kẹ́ | n. | *bicycle* |
| ẹ̀rẹ̀kẹ́ | n. | *cheek* |
| ẹyẹ | n. | *bird* |
| ẹ̀yẹ | n. | *honor* |
| jẹ́jẹ́ | adv. | *gently* |
| ẹ̀gẹ́ | n. | *cassava* |
| ẹsẹ̀ | n. | *leg* |
| ẹ̀pà | n. | *peanut* |
| ẹní | n. | *mat* |
| ẹkùn | n. | *leopard* |

**Tone practice:**

| | | |
|---|---|---|
| iṣẹ́ | n. | *work* |
| ìṣẹ́ | n. | *poverty* |
| ẹ̀jẹ̀ | n. | *blood* |
| ẹ̀jẹ́ | n. | *pledge, oath* |

### Tongue twisters:

Ọdẹ́ jẹ ẹ̀já lórí kẹ̀kẹ́.
*The hunter ate fish on the bike.*

Pẹ̀lẹ́pẹ̀lẹ́ lọdẹ ń dẹ̀gbẹ́. (Proverb)
*A hunter hunts carefully.*

/i/

| | | |
|---|---|---|
| igi | n. | *tree, stick* |
| ìrì | n. | *dew* |
| ìbí | n. | *birth* |
| Bísí | n. | *name of a person* |
| ìdì | n. | *bundle* |
| ìdí | n. | *butt, the reason why* |
| iyì | n. | *honor* |
| idẹ | n. | *brass* |
| ìdílé | n. | *family, household* |
| ìdíwọ́ | n. | *obstacle* |

### Tone practice:

| | | |
|---|---|---|
| ife | n. | *cup* |
| ìfé | n. | *whistle* |
| | | |
| ìdì | n. | *bundle* |
| ìdí | n. | *butt, the reason why* |

### Tongue twisters:

Ìrírí Rísí ní ìrìnàjòo rẹ̀ yani lẹ́nu.
*Rísí's experience on her trip surprised everyone.*

Ìdí igi ni Jídé wà.
*Jídé is by the tree.*

Bísí dúró ní ìdí igi gíga.
*B*ísí *stands by the tall tree.*

 CC – 2011 The University of Texas at Austin

/o/

| | | |
|---|---|---|
| owó | n. | *money* |
| òwò | n. | *trade* |
| opó | n. | *widow* |
| òpó | n. | *pillar* |
| òkúta | n. | *stone* |
| Òjó | n. | *name of a male person* |
| ojo | n. | *coward* |
| òjò | n. | *rain* |
| olówó | n. | *rich person* |
| òróró | n. | *ground nut oil, peanut oil* |

**Tone practice:**

| | | |
|---|---|---|
| Òjó | n. | *name of a person (male)* |
| òjò | n. | *rain* |
| opó | n. | *widow* |
| òpó | n. | *pillar, post* |
| owó | n. | *money* |
| òwò | n. | *trade* |

**Tongue twisters:**

Òjó gbowó lọ́wọ́ olówó l'Ówódé.
*Òjó got the money from the wealthy person in O*wódé town*.*

Olú dòróró sínú odóo Màmáa Tolú.
*Olú poured the peanut oil into Tolú's mother's mortar.*

/ọ/

| | | |
|---|---|---|
| ọwọ́ | n. | *hand* |
| ọwọ̀ | n. | *broom* |
| ọ̀wọ̀ | n. | *respect* |
| Ọ̀wọ̀ | n. | name of a Yorùbá town |
| ọkọ́ | n. | *hoe* |
| ọ̀kọ̀ | n. | *spear* |
| ọkọ̀ | n. | *vehicle* |
| ọkọ | n. | *husband* |
| ọ̀pọ̀lọ́ | n. | *toad* |
| ọpọlọ | n. | *brain* |
| kọ̀lọ̀kọ̀lọ̀ | n. | *fox* |
| kọ́kọ́rọ́ | n. | *key* |

**Tone practice:**

| | | |
|---|---|---|
| ọ̀kọ̀ | n. | *spear* |
| ọkọ́ | n. | *hoe* |
| ọpọlọ | n. | *brain* |
| ọ̀pọ̀lọ́ | n. | *frog* |

**Tongue twisters:**

Ọpọlọ ọ̀dọ́ náà ń ṣiṣẹ́ bíi ọpọlọ kọ̀lọ̀kọ̀lọ̀
*The brain of the young person works like the brain of a fox. (S/he is canny like a fox.)*

Ọlá jọ̀kọ̀ sọ́kọ̀ ọ̀gáa rẹ̀.
*Ọlá threw a spear at the vehicle of his boss.*

/u/

| | | |
|---|---|---|
| kúkúrú | adj. | *short* |
| burúkú | adj. | *bad* |
| dúdú | adj. | *black/dark* |
| kú | v. | *to die* |
| lù | v. | *beat* |
| tutù | v./adj. | *to be cold* |
| lú | v. | *to mingle* |
| tú | v. | *untie* |
| fọ̀ | v. | *to wash* |
| ìlù | n. | *drum* |

**Tone practice:**

| | | |
|---|---|---|
| lú | v. | *to mingle* |
| lù | v. | *to beat* |
| lu | v. | *to make a hole(under)* |
| tú | v. | *untie* |
| tù | v. | *to ease, to soothe* |
| tu | v. | *to uproot* |

**Tongue twisters:**

Mo lu ìlùu dùndún nílúu Lolú.
*I beat the dùndún drum in Lolú's town.*

Ooru búrúkú mú Olú ní òru.
*Olú was very hot in the middle of the night.*

# Pronunciation and Tone Practice

## Oral Vowels - Part I (No tones tested)

Listen to your teacher for the pronunciation of the words in the left column. There is an oral vowel underlined in the word. Check the appropriate box where the underlined oral vowel belongs.

| ọ̀rọ̀ | [a] | [e] | [ẹ] | [i] | [o] | [ọ] | [u] |
|---|---|---|---|---|---|---|---|
| 1. Ìbàdàn | | | | | | | |
| 2. ẹyẹ | | | | | | | |
| 3. ojú | | | | | | | |
| 4. igi | | | | | | | |
| 5. edé | | | | | | | |
| 6. ọmọ | | | | | | | |
| 7. owó | | | | | | | |
| 8. èdè | | | | | | | |
| 9. ọkọ | | | | | | | |
| 10. àdá | | | | | | | |
| 11. ajá | | | | | | | |
| 12. òwò | | | | | | | |
| 13. ọkọ̀ | | | | | | | |
| 14. àjà | | | | | | | |
| 15. ọwọ́ | | | | | | | |
| 16. ọkọ́ | | | | | | | |
| 17. odò | | | | | | | |
| 18. ọ̀wọ̀ | | | | | | | |
| 19. odó | | | | | | | |
| 20. ọ̀do | | | | | | | |

 CC – 2011 The University of Texas at Austin

# Oral Vowels - Part II (Tones tested)

Listen to your teacher for the pronunciation of the words in the left column. There is an oral vowel underlined in the word. Check the appropriate box where the underlined oral vowel belongs.

| ọ̀rọ̀ | [à] | [á] | [a] | [è] | [é] | [e] | [ẹ̀] | [ẹ́] | [ẹ] |
|---|---|---|---|---|---|---|---|---|---|
| 1. Ìbàdàn | | | | | | | | | |
| 2. ẹyẹ | | | | | | | | | |
| 3. ọyẹ́ | | | | | | | | | |
| 4. Ifẹ̀ | | | | | | | | | |
| 5. ọ̀fẹ́ | | | | | | | | | |
| 6. èdè | | | | | | | | | |
| 7. edé | | | | | | | | | |
| 8. eré | | | | | | | | | |
| 9. ère | | | | | | | | | |
| 10. àpá | | | | | | | | | |
| 11. apá | | | | | | | | | |
| 12. ẹsẹ̀ | | | | | | | | | |
| 13. àrá | | | | | | | | | |
| 14. ẹ̀ṣẹ̀ | | | | | | | | | |
| 15. ara | | | | | | | | | |
| 16. àrà | | | | | | | | | |
| 17. ẹja | | | | | | | | | |
| 18. erè | | | | | | | | | |
| 19. àpẹẹrẹ | | | | | | | | | |
| 20. ìbéèrè | | | | | | | | | |
| 21. apẹ̀rẹ̀ | | | | | | | | | |
| 22. afẹ́fẹ́ | | | | | | | | | |
| 23. adé | | | | | | | | | |
| 24. ọ̀gẹ̀dẹ̀ | | | | | | | | | |
| 25. ìbẹ̀rẹ̀ | | | | | | | | | |

## Oral Vowels - Part II (Tones tested) Continued

Listen to your teacher for the pronunciation of the words in the left column. There is an oral vowel underlined in the word. Check the appropriate box where the underlined oral vowel belongs.

| ọ̀rọ̀ | [ì] | [i] | [í] | [ò] | [o] | [ó] | [ọ̀] | [ọ] | [ọ́] | [ù] | [u] | [ú] |
|---|---|---|---|---|---|---|---|---|---|---|---|---|
| 1. ìjì | | | | | | | | | | | | |
| 2. ojú | | | | | | | | | | | | |
| 3. òjò | | | | | | | | | | | | |
| 4. abọ́ | | | | | | | | | | | | |
| 5. ìdí | | | | | | | | | | | | |
| 6. ọjọ́ | | | | | | | | | | | | |
| 7. àbọ̀ | | | | | | | | | | | | |
| 8. òjó | | | | | | | | | | | | |
| 9. oṣù | | | | | | | | | | | | |
| 10. iṣu | | | | | | | | | | | | |
| 11. etí | | | | | | | | | | | | |
| 12. ọ̀bọ | | | | | | | | | | | | |
| 13. opó | | | | | | | | | | | | |
| 14. òpó | | | | | | | | | | | | |
| 15. ìwé | | | | | | | | | | | | |
| 16. irú | | | | | | | | | | | | |
| 17. igi | | | | | | | | | | | | |
| 18. ọ̀wọ́ | | | | | | | | | | | | |
| 19. ìka | | | | | | | | | | | | |
| 20. ẹrù | | | | | | | | | | | | |
| 21. ẹrú | | | | | | | | | | | | |
| 22. ọkọ | | | | | | | | | | | | |
| 23. ọkọ́ | | | | | | | | | | | | |
| 24. ṣíbí | | | | | | | | | | | | |
| 25. òkúta | | | | | | | | | | | | |

# Nasal Vowels

Standard Yorùbá language has five nasal vowels: -an; -ẹn; -in; -ọn; -un

## /an/

| | | |
|---|---|---|
| iyán | n. | *pounded yam* |
| ìran | n. | *generation* |
| itan | n. | *thigh* |
| ìtàn | n. | *story* |
| ọ̀sán | n. | *afternoon* |
| Ìbàdàn | n. | *name of a Yorùbá city* |

### Tone practice:

| | | |
|---|---|---|
| itan | n. | *thigh* |
| ìtàn | n. | *story* |
| | | |
| ọsàn | n. | *orange* |
| ọ̀sán | n. | afternoon |

## /ọn/

| | | |
|---|---|---|
| ìbọn | n. | *gun* |
| ọpọ́n | n. | *wooden bowl* |
| àpọ́n | n. | *a bachelor* |
| ahọ́n | n. | *tongue* |
| ọgbọ́n | n. | *wisdom* |
| ọgbọ̀n | n. | *thirty* |
| àgbọn | n. | *coconut* |
| agbọ̀n | n. | *basket* |
| àgbọ̀n | n. | *chin* |

### Tone practice:

| | | |
|---|---|---|
| ọgbọ́n | n. | *wisdom* |
| ọgbọ̀n | n. | *thirty* |
| | | |
| àgbọn | n. | *coconut* |
| agbọ̀n | n. | *basket* |
| àgbọ̀n | n. | *chin* |

## /ẹn/

| | | |
|---|---|---|
| ìyẹn | adj. | *that one* |

| | | |
|---|---|---|
| ẹnẹn | adv. | *yes* |
| ẹ̀n-ẹ́n-ẹ̀n! | adv. | *really? Is that so?* |
| yẹn | pr. | *that* |

It is important to note that not very many words end in **/ẹn/** in Yorùbá.

### /in/

| | | |
|---|---|---|
| eyín | n. | *tooth* |
| ẹ̀yìn | n. | *back* |
| ẹ̀yin | pr. | *you (plural)* |
| ìgbín | n. | *snail* |
| ìpín | n. | *portion* |
| irin | n. | *iron, metal* |
| ìrìn | n. | *walk* |
| ẹ̀rín | n. | *laughter* |
| ẹṣin | n. | *horse* |
| ìsìn | n. | *worship* |
| ẹ̀sín | n. | *shame* |

### Tone practice:

| | | |
|---|---|---|
| ẹ̀yìn | n. | *back* |
| ẹ̀yin | pr. | *you (plural)* |

| | | |
|---|---|---|
| irin | n. | *iron, metal* |
| ìrìn | n. | *walk* |

### /un/

| | | |
|---|---|---|
| irun | n. | *hair* |
| ìdun | n. | *bed bug* |
| ẹfun | n. | *chalk* |
| ọ̀bùn | n. | *a dirty person* |
| okùn | n. | *rope* |
| òkun | n. | *ocean* |
| ọ̀run | n. | *heaven* |
| ọrùn | n. | *neck* |
| ọdún | n. | *year* |
| adùn | n. | *sweetness, flavor* |

### Tone practice:

| | | |
|---|---|---|
| okùn | n. | *rope* |

òkun n. *ocean*
ọ̀run n. *heaven*
ọrùn n. *neck*

## Nasal Vowels - Part I (No tones tested)

Listen to your teacher for the pronunciation of the words in the left column. There is a nasal vowel underlined in the word. Check the appropriate box where the underlined nasal vowel belongs.

| ọ̀rọ̀ | [an] | [ẹn] | [in] | [ọn] | [un] |
|---|---|---|---|---|---|
| 1. Ìbàdàn | | | | | |
| 2. òórùn | | | | | |
| 3. Ọ̀ṣun | | | | | |
| 4. ọgbọ́n | | | | | |
| 5. ikàn | | | | | |
| 6. àgbọn | | | | | |
| 7. ọgbọ̀n | | | | | |
| 8. irin | | | | | |
| 9. ikùn | | | | | |
| 10. òyìnbó | | | | | |
| 11. òòrùn | | | | | |
| 12. òògùn | | | | | |
| 13. iyán | | | | | |
| 14. ahọ́n | | | | | |
| 15. erin | | | | | |
| 16. ikùn | | | | | |
| 17. ọ̀jọ̀gbọ́n | | | | | |
| 18. iyàn | | | | | |
| 19. àgbọ̀n | | | | | |
| 20. eyín | | | | | |
| 21. obìnrin | | | | | |
| 22. ibùsùn | | | | | |
| 23. orín | | | | | |
| 24. ọ̀dùnkún | | | | | |
| 25. itan | | | | | |
| 26. orin | | | | | |
| 27. àkìtàn | | | | | |
| 28. igun | | | | | |
| 29. àyẹn | | | | | |
| 30. ikun | | | | | |

# Nasal Vowels - Part II (Tones tested)

Listen to your teacher for the pronunciation of the words in the left column. There is a nasal vowel underlined in the word. Check the appropriate box where the underlined nasal vowel belongs.

| ọ̀rọ̀ | [àn] | [án] | [an] | [ẹ̀n] | [ẹ́n] | [ẹn] | [ìn] | [ín] | [in] | [ọ̀n] | [ọ́n] | [ọn] | [ùn] | [ún] | [un] |
|---|---|---|---|---|---|---|---|---|---|---|---|---|---|---|---|
| 1. Ìbàdàn | | | | | | | | | | | | | | | |
| 2. òórùn | | | | | | | | | | | | | | | |
| 3. Ọ̀ṣun | | | | | | | | | | | | | | | |
| 4. ọgbọ́n | | | | | | | | | | | | | | | |
| 5. ikàn | | | | | | | | | | | | | | | |
| 6. àgbọn | | | | | | | | | | | | | | | |
| 7. ọgbọ̀n | | | | | | | | | | | | | | | |
| 8. irin | | | | | | | | | | | | | | | |
| 9. aáyán | | | | | | | | | | | | | | | |
| 10. òyìnbó | | | | | | | | | | | | | | | |
| 11. òòrùn | | | | | | | | | | | | | | | |
| 12. òògùn | | | | | | | | | | | | | | | |
| 13. iyán | | | | | | | | | | | | | | | |
| 14. ahọ́n | | | | | | | | | | | | | | | |
| 15. erin | | | | | | | | | | | | | | | |
| 16. ikùn | | | | | | | | | | | | | | | |
| 17. Ọ̀jọ̀gbọ́n | | | | | | | | | | | | | | | |
| 18. iyàn | | | | | | | | | | | | | | | |
| 19. àgbọ̀n | | | | | | | | | | | | | | | |
| 20. eyín | | | | | | | | | | | | | | | |
| 21. obìnrin | | | | | | | | | | | | | | | |
| 22. ibùsùn | | | | | | | | | | | | | | | |
| 23. orín | | | | | | | | | | | | | | | |
| 24. ọ̀dùnkún | | | | | | | | | | | | | | | |
| 25. itan | | | | | | | | | | | | | | | |
| 26. orin | | | | | | | | | | | | | | | |
| 27. àkìtàn | | | | | | | | | | | | | | | |
| 28. igun | | | | | | | | | | | | | | | |
| 29. ìyẹn | | | | | | | | | | | | | | | |
| 30. ikun | | | | | | | | | | | | | | | |

## The syllabic [m] and [n]

**[m]** and **[n]** are considered nasal consonants. They are allophones of the same phoneme/n/. However, they can act in capacity as syllabic nasals because they behave like vowels on which tones can be marked. In other words, they can stand on their own just like a syllable. Examples of the syllable **/n/** can be found in the following:

| | | |
|---|---|---|
| Adéńrelé | a/dé/ń/re/lé | *name of a person* |
| dùǹdú | dù/ǹ/dú | *fried yam* |
| Bánkẹ́ | bá/n/kẹ́ | *a girl's name* |
| gbangba | gba/n/gba | *open arena* |
| kọ̀ǹkọ̀ | kọ̀/ǹ/kọ̀ | *toad* |
| gbàǹgbà | gbà/ǹ/gbà | *very big* |
| Déńdè | Dé/ń/dè | *name of a male person* |
| Bọ́láńlé | Bọ́/lá/ń/lé | *name of a person* |
| aláǹgbá | a/lá/ǹ/gbá | *lizard* |

| | | |
|---|---|---|
| àǹkàrá | à/ǹ/kà/rá | *a type of fabric* |
| àǹfàànní | à/ǹ/fà/à/ní | *benefit* |

Examples of the syllable **/m/** can be found in the following:

| | | |
|---|---|---|
| Bímbọ́lá | Bí/m/bọ́/lá | *name of a person* |
| Bímpé | Bí/m/pé | *name of a boy or girl* |

 CC – 2011 The University of Texas at Austin

## Kọ́ńsónáǹtì Yorùbá (*Yorùbá Consonants*)

Yorùbá consonants are depicted below in various environments in which they can occur: *word initially* (at the beginning of a word), *intervocalically* (between vowels), or *word finally* (at the end of a word).

/b/

| | | |
|---|---|---|
| bàbá | n. | *father* |
| bó | v. | *to peel* |
| bẹ̀rẹ̀ | v. | *to start; to squat* |
| Bísí | n. | *name of a male or female Yorùbá person* |
| bàtà | n. | *shoe* |
| bò | v. | *to cover* |
| bẹ́ | v. | *to jump; to puncture* |
| bẹ̀rù | v. | *to fear* |
| búburú | adj. | *wicked* |
| ìbínú | v. | *anger* |

### Tone practice:

| | | |
|---|---|---|
| bí | v. | *to deliver a baby* |
| bì | v. | *to throw up* |
| bi | v. | *to ask* |
| | | |
| bọ́ | v. | *to be free* |
| bọ̀ | v. | *to boil/parboil* |
| bọ | v. | *to worship* |

### Tongue twisters:

Bísí bá bàbá bọ́ bàtà.
*Bísí helped father take off his shoe(s).*

<u>Drum song</u>
Bá a bá léni
Bá a bá báni
Ìwọ̀n là á báníí ṣọ̀tá mọ

### Translation:

If we pursue people in order to wickedly hurt them and we fail to get a hold on them, we should stop pursuing them. It is not good to be an eternal enemy to people.

 CC – 2011 The University of Texas at Austin

## /d/

| | | |
|---|---|---|
| ẹ̀dá | n. | *human being* |
| ìdàmú | n. | *worry* |
| ìdálẹ̀ | n. | *a foreign country, city, town, village* |
| ọ̀ọ̀dẹ̀/ọ̀dẹ̀dẹ̀ | n. | *backyard* |
| dáríjì | v. | to forgive |
| ìdáwó | n. | *money contribution* |
| dáwó | v. | *to contribute money* |
| dánilójú | adv. | *to be sure of, to be certain* |
| ọ̀dẹ̀ | n. | *a stupid person* |
| ọdẹ | n. | *a hunter* |

### Tone practice:

| | | |
|---|---|---|
| dé | v. | *to cover, to arrive, to wear(e.g a crown / a hat)* |
| dè | v. | *to tie down* |
| dẹ̀ | v. | *to soften* |
| dẹ | v. | *to trap* |
| edé | n. | *shrimp* |
| èdè | n. | *language* |
| ọ̀dẹ̀ | n. | *a stupid person* |
| ọdẹ | n. | *a hunter* |

### Tongue Twisters:

Adé dé adé ọba ní Ayédé.
*Adé (name of a person) wore the crown of the king in the city of Ayédé.*

Dàda tutù bí ẹyẹ àdàbà.
*Dàda (name of a boy) is gentle like a dove.*

## /f/

| | | |
|---|---|---|
| Ifẹ̀ | n. | *a Yorùbá city in Nigeria* |
| ìfẹ́ | n. | *love* |
| afẹ́fẹ́ | n. | *breeze* |
| funfun | adj. | *white* |
| Ìfàkì | n. | *a Yorùbá town in Nigeria* |
| fẹ́ràn | v. | *to like* |
| ẹfun | n. | *chalk* |
| fún | v. | *to give* |
| fìlà | n. | *hat, cap* |
| Fẹ́mi | n. | *name of a person* |

 CC – 2011 The University of Texas at Austin

## Tone practice:

| | | |
|---|---|---|
| fẹ́ | v. | *to blow* |
| fẹ̀ | v. | *to widen* |
| fọ̀ | v. | *to wash* |
| fọ́ | v. | *to break* |

## Tongue Twisters:

Fẹ́mi fẹ́ràn*an* fìlà funfun.
*Fẹ́mi likes white hats.*

Afẹ́fẹ́ fẹ́ ìyẹ́ funfun náà lọ.
*The breeze blew away the white feather.*

Fọlá fọṣọ funfun fún Fẹ́mi.
*Fọlá washed the white clothe for Fẹ́mi.*

## /g/

| | | |
|---|---|---|
| ọ̀gá | n. | *boss* |
| ògo | n. | *glory* |
| ogún | n. | *twenty; inheritance* |
| ogun | n. | *war* |
| Ògún | n. | *god of iron* |
| ọ̀gẹ̀dẹ̀ | n. | *plantain* |
| agogo (aago) | n. | *clock, wristwatch, time* |
| igi | n. | *tree* |
| àga | n. | *chair* |
| gé | v. | *to cut* |

## Tone practice:

| | | |
|---|---|---|
| gùn | v. | *to climb* |
| gùn | adj. | to be *lengthy, tall* |
| gún | v. | *to pound, to mash* |

## Tongue twisters:

Gbénga gé igi gíga.
*Gbénga cut a tall tree.*

**Proverb**:
Igi gogoro má gùn-ún mi lójú, òkèèrè la ti ń wò ó.
*Be mindful of impending troubles.*

The **[kp]** and **[gb]** are referred to as plosive consonants. They have double places of articulation(labial and velum).. Hence they are labio-velar consonants. Their manner of articulation is plosive. Hence, they are both labiovelar plosives. Their difference is in voicing. The sounds indicate double articulation. The letter **/p/** is represented as **[kp]** in Yorùbá pronunciation. The **/k/** and the **/p/** in the **[kp],** and the **/g/** and the **/b/** in **[gb]** are not separate but pronounced together.

/gb/

| | | |
|---|---|---|
| gbogbo | adj. | *all* |
| gbòǹgbò | n. | *root* |
| àgbà | n. | *the elderly* |
| ẹgbẹ́ | n. | *group, people, association, organization* |
| ẹ̀gbẹ́ | prep. | *beside, side* |
| agbádá | n. | *Yorùbá men's flowing garment* |
| àgbàdo | n. | *corn* |
| aláǹgbá | n. | *lizard* |
| agbòòrùn | n. | *umbrella* |
| ìgbàgbọ́ | n. | *faith, belief* |

**Tone practice:**

| | | |
|---|---|---|
| agbọ̀n | n. | *basket* |
| àgbọn | n. | *coconut* |
| agbọ́n | n. | *wasp* |
| | | |
| àgbàrá | n. | *flood* |
| agbára | n. | *power* |

**Tongue Twisters:**

Gbogbo àgbààgbà lọ sí ọjàa Gbági.
*All the elderly people went to Gbagi market.*

Gbogbo aláǹgbá ń sá láńgbáláńgbá nínú àgbàlá.
*All the lizards are running around in the compound.*

/h/

| | | |
|---|---|---|
| ihò | n. | *pit, hole* |
| wàhálà | n. | *trouble* |
| Wọlé | n. | *name of a male person* |
| hó | v. | *to peel* |
| há | v. | *to distribute* |
| há | adj. | *tight; narrow* |
| ahọ́n | n. | *tongue* |
| ẹlẹ́hàá | n. | *a veiled woman* |
| họ | v. | *to scratch; to run away* |
| ìhà | n. | *side; region* |

**Tone practice:**

| | | |
|---|---|---|
| han | v. | *to scream* |
| hàn | v. | *to appear* |
| hán | v. | *to grasp (something)* |
| | | |
| há | v. | *to be tight; to distribute* |
| ha | v. | *to scratch* |

**Tongue Twisters:**
Híhanrun tí bàbáa Délé ń hanrun jẹ́ wàhálà.
*The snoring of Délé's father is a problem.*

/j/

[dʒ]

| | | |
|---|---|---|
| jó | v. | *to dance* |
| àjò | n. | *trip, travel* |
| ọjà | n. | *market* |
| ìjì | n. | *storm* |
| jà | v. | *to fight* |
| ọjọ́ | n. | *day* |
| òjò | n. | *rain* |
| oúnjẹ | n. | *food* |
| ijù | n. | *jungle* |
| ìjà | n. | *fight* |

**Tone practice:**

| | | |
|---|---|---|
| ẹ̀jẹ̀ | n. | *blood* |
| ẹ̀jẹ́ | n. | *oath* |

**Tongue Twisters:**

Ìjí jà ní ọjọ́ ọjà ní ìjeje.
*There was a storm on market day seven days ago.*

Jùmọ̀kẹ́ jùdí ní ajọ ijó.
*Jùmọ̀kẹ́ shook her butt at the dance association.*

/k/

| | | |
|---|---|---|
| ọkà (àmàlà) | n. | *cooked yam flour* |
| ọká | n. | *cobra* |
| oríkì | n. | *praise name* |

| | | |
|---|---|---|
| kíákíá | adv. | *quickly* |
| eku | n. | *rat* |
| kẹ̀kẹ́ | n. | *bicycle* |
| ọkùnrin | n. | *man, male* |
| ẹ̀rẹ̀kẹ́ | n. | *cheek* |
| èké | n. | *gossip* |
| ẹkùn | n. | *leopard* |

**Tone practice:**

| | | |
|---|---|---|
| ọkọ̀ | n. | *vehicle* |
| ọkọ | n. | *husband* |
| ọkọ́ | n. | *hoe* |
| ọ̀kọ̀ | n. | *spear* |

**Tongue twisters:**

Kẹ́mi kí Kíkẹ́ káàárọ̀.
*Kẹ́mi (a name of a female person) greeted Kíkẹ́ (a name of a female person) 'good morning.'*

Kíkẹ́ kí Kẹ́mi káàárọ̀
*Kíkẹ́ (a name of a female person) greeted Kẹ́mi(a name of a female person) 'good morning.'*

**Proverb:**
Kíkéré ni abẹ́rẹ́ ń kéré, kì í ṣe mímì fún adìẹ
*Though the needle is small, it cannot be swallowed by a hen.*

/l/

| | | |
|---|---|---|
| lé | v. | *to chase* |
| lè | v. | *can, to be able to* |
| lẹ | adj. | *to be lazy* |
| lù | v. | *to beat* |
| ọlá | n. | *honor; wealth* |
| Lékan | n. | *name of a male person* |
| labalábá | n. | *butterfly* |
| Àlàbá | n. | *name given to the second child born after twins* |
| àlá | n. | *dream* |
| láti | prep. | *in order to; from* |

**Tone practice:**

| | | |
|---|---|---|
| lọ | v. | *go, went* |
| lọ̀ | v. | *to blend* |
| | | |
| là | v. | *to cut; to be free* |
| lá | v. | *to lick* |

**Tongue twister:**

Lọlá lá àlá lábà Àlàbá.
*Lọlá dreamed in Àlàbá's hut.*

**/m/**

| | | |
|---|---|---|
| méjì | adj. | *two* |
| ìmọ̀ | n. | *knowledge* |
| ọ̀mọ̀wé | n. | *a PhD degree holder* |
| ọmọ | n. | *child* |
| amọ̀ | n. | *clay* |
| ọmọbìnrin | n. | *a young female person* |
| ọmọkùnrin | n. | *a young male person* |
| màmá | n. | *mother* |
| omi | n. | *water* |
| mọlémọlé | n. | *builder* |

**Tone practice:**

| | | |
|---|---|---|
| mọ́ | adj. | *to be clean* |
| mọ̀ | v. | *to know* |

**Tongue twisters:**

Mo mu omi ní ilée màmàá Máyọ̀wá.
*I drank water at Máyọ̀wá's mother's house.*

Màmáà mi mu omiì mi.
*My mom drank my water.*

**/n/**

| | | |
|---|---|---|
| ní | v. | *to have* |
| níbí | adv. | *here* |
| níbo | interro. | *where?* |
| nípọn | adj. | *thick* |
| níwájú | adv. | *in front of, ahead* |
| nísìnyí | adv. | *now* |
| níbẹ̀yẹn | prep. | *over there* |
| nìkan | adj. | *only, alone* |
| nù | v. | *to clean* |
| náírà | n. | *náírà (Nigerian currency)* |

**Tone practice:**

| | | |
|---|---|---|
| ní | v. | *to have* |
| ni | v. | *to be* |
| | | |
| ná | v. | *to haggle or bargain* |
| nà | v. | *to beat (someone)* |

**Tongue Twisters:**

Níyì ná náírà nílé ànaa rẹ̀.
*Níyì spent náírà at the in-law's house.*

Níran náwó nínààkúnàá.
*Níran spent money extravagantly.*

**/p/ = [kp]**

| | | |
|---|---|---|
| àpá | n. | *scar* |
| ẹ̀pà | n | *peanut* |
| epo | n. | *cooking oil, gas for vehicle* |
| àpò | n. | *bag* |
| pọ̀tọ̀pọ́tọ̀ | n. | *puddle* |
| pátápátá | adv. | *completely* |
| pín | n. | *divide* |
| pátá | n. | *underwear* |
| páálí | n. | *cardboard, cardboard box* |
| pàtàkì | adj. | *important, crucial* |

**Tone practice:**

| | | |
|---|---|---|
| apá | n. | *arm* |
| àpà | n. | *a wasteful person* |
| | | |
| pọ́n | adj. | *to be ripe* |
| pọ̀n | v. | *to carry on the back (e.g. a baby)* |

**Tongue Twisters:**

Pàkútée Péjú pa ẹyẹ àparò.
*Péjú's trap killed the partridge.*

Paríọlá pín ẹ̀pà náà.
*Paríọlá (name of a male person) divided the peanuts.*

Pàdé *(name of a male person)* pejò ní pápáa bọ́ọ̀lù Àpápá .
*Pàdé killed a snake on Àpápá soccer field.*

 CC – 2011 The University of Texas at Austin

### /r/

| | | |
|---|---|---|
| ara | n. | *body* |
| rí | v. | *to see* |
| rà | v. | *to buy* |
| rere | adj. | *nice, good* |
| rẹ́rìnín | v. | *to laugh* |
| rárá | adv. | not *at all* |
| ronú | v. | *to think* |
| rojọ́ | v. | *to complain* |
| ròyìn | v. | *to report* |
| rántí | v. | *to remember* |

**Tone practice:**

| | | |
|---|---|---|
| rò | v. | *to think, to stir* |
| ró | v. | *to tie as in wrapper/cloth* |
| | | |
| eré | n. | *game, play* |
| èrè | n. | *profit* |
| | | |
| erè | n. | *boa constrictor* |
| ère | n. | *statue* |

**Tongue Twisters:**

Rírí tí Rẹ̀mí rí ọ̀rẹ́ẹ̀ mi Rántí mú inuù Rẹ̀mí dùn.
*Rẹ̀mí became happy on* se*eing my good friend Rántí.*

Rẹ̀mí ra ìrẹsì ní Rẹ́mọ.
*Rẹ̀mí bought rice in Rẹ́mọ.*

### /s/

| | | |
|---|---|---|
| ìrẹsì | n. | *rice* |
| ìwọ̀sí | n. | *insult* |
| sùúrù | n. | *patience* |
| ẹsẹ̀ | n. | *leg* |
| ìsìn | n. | *worship* |
| sọ̀rọ̀ | v. | *to speak* |
| Similólú | n. | *name of a female person* |
| sinmi | n. | *to rest* |
| àìsàn | n. | *sickness* |
| àsè | n. | *a party, a get-together* |

**Tone practice:**

| | | |
|---|---|---|
| sìn | v. | *to worship* |
| sín | v. | *to sneeze* |
| sin | v. | *to bury* |
| | | |
| ìsìn | n. | *worship* |
| ẹ̀sín | n. | *shame, reproach* |
| ẹ̀sín | n. | *religion* |

**Tongue Twisters:**

Similọ́lá sinmi lọ́jọ́ ìsinmi.
*Similọ́lá rested on Sunday.*

Sanmí (name of a male person) binú sí Sánní.
*Sanmí was mad at Sánní.*

## /ṣ/

/ṣ/ is pronounced as 'sh' as in 'shy'.

| | | |
|---|---|---|
| ṣòkòtò | n. | *a pair of pants* |
| ẹṣin | n. | *horse* |
| iṣu | n. | *yam* |
| aṣọ | n. | *cloth, fabric* |
| aláṣọ | n. | *the seller/owner of fabric/cloth* |
| Ṣadé | n. | *name of a female person* |
| Ṣọlá | n. | *name of a person* |
| ṣòro | adj. | *to be difficult* |
| àṣà | n. | *custom, tradition* |
| àṣá | n. | *hawk* |
| àṣẹ | n. | *command* |

**Tone practice:**

| | | |
|---|---|---|
| ṣẹ́ | v. | *to break* |
| ṣẹ̀ | v. | *to sin, to commit a crime* |
| | | |
| àṣà | n. | *custom, tradition* |
| àṣá | n. | *hawk* |

**Tongue Twisters:**

Ṣadé ṣubú níwájúu Ṣọlá.
*Ṣadé fell in front of Ṣọlá.*

Ṣé Ṣọlá ń ṣiṣẹ́ ní ṣọ́ọ̀bù Ṣẹ̀yẹ?
*Does Ṣọlá work in Ṣẹ̀yẹ's shop?*

/t/

| | | |
|---|---|---|
| atẹ́gùn | n. | *air* |
| àtẹ́lẹwọ́ | n. | *palm of the hand* |
| àti | conj. | *and* |
| ata | n. | *pepper* |
| ọ̀tẹ̀ | n. | *conspiracy* |
| ọtí | n. | *alcoholic beverage* |
| gbókìtì | v. | to *summersault* |
| tẹ́lẹ̀tẹ́lẹ̀ | adv. | *originally, before* |
| òtítọ́ | n. | *truth* |
| bàtà | n. | *shoe* |

### Tone practice:

| | | |
|---|---|---|
| [Sáńgo] Ọ̀tà | n. | *name of a Yorùbá town* |
| ọ̀tá | n. | *enemy* |
| | | |
| tọ̀ | v. | *to urinate* |
| tọ́ | v. | *to raise, e.g.  a child* |

### Tongue Twister:

Títí ta atá ní títì.
*Títí sold peppers on the street.*

### Proverb:
Atètè sùn làtètè jí.
*Early to bed, early to rise.*

/w/

| | | |
|---|---|---|
| ìwé | n. | *book* |
| ìwà | n. | *behavior* |
| wéréwéré | adv. | *quickly* |
| wẹẹrẹ | adj. | *small, little* |
| wàhálà | n. | *trouble* |
| wọ́ | v. | *to be crooked* |
| wù | v. | *to like* |
| wà | v. | *to exist* |
| wá | v. | *to come* |
| Wọlé | v. | *name of a male person* |

 CC – 2011 The University of Texas at Austin

**Tone practice:**

| | | |
|---|---|---|
| ìwé | n. | *book* |
| iwe | n. | *gizzard* |
| | | |
| wọlé | v. | *to enter* |
| Wẹ̀mímọ́ | adj. | *name of a person* |

**Tongue Twisters:**

Wálé wọlée Wẹ̀mímọ́.
*Wálé entered Wẹ̀mímọ́'s house.*

Wálé  wọlée Wọlé.
*Wálé entered Wọlé's house.*

Wálé wale mi.
*Wálé came to my house.*

/y/

| | | |
|---|---|---|
| iyanrìn | n. | *sand* |
| yàtọ̀ | adj. | *different* |
| yìnyín | n. | *ice* |
| yànmùyánmú | n. | *mosquito* |
| yọjú | v. | *to appear* |
| yìn | v. | *to praise* |
| Yínká | n. | *name of a person* |
| Yẹmí | n. | *name of a person* |
| yọyínyọyín | n. | *a dentist* |
| ẹ̀yìn | n. | *back* |

**Tone practice:**

| | | |
|---|---|---|
| yọ̀ | v. | *to rejoice, to slip* |
| yọ́ | adj. | *to be slimy* |
| | | |
| yàrá | n. | *room* |
| yarí | n. | *to refuse* |

**Tongue Twisters:**

Ọ̀yàyà ìyáa Yẹmi máyé yẹ ẹ́.
*Yẹmi's mom's enthusiasm is rewarding.*

Ayé yẹ Yẹlé ní ìlú Ọyọ́.
*Life is pleasant with Yẹlé in Ọ̀yọ́ town.*

 CC – 2011 The University of Texas at Austin

## Consonants

Listen to your teacher for the pronunciation of the words in the left column. There is a consonant underlined in the word. Check the appropriate box where the underlined consonant belongs.

| ọ̀rọ̀ | [b] | [d] | [f] | [g] | [gb] | [h] | [j] | [k] | [l] | [m] | [n] | [p] | [r] | [s] | [ṣ] | [t] | [w] | [y] |
|---|---|---|---|---|---|---|---|---|---|---|---|---|---|---|---|---|---|---|
| 1. adé | | | | | | | | | | | | | | | | | | |
| 2. labalábá | | | | | | | | | | | | | | | | | | |
| 3. igi | | | | | | | | | | | | | | | | | | |
| 4. aṣọ | | | | | | | | | | | | | | | | | | |
| 5. asẹ́ | | | | | | | | | | | | | | | | | | |
| 6. bàtà | | | | | | | | | | | | | | | | | | |
| 7. fìlà | | | | | | | | | | | | | | | | | | |
| 8. ọ̀gá | | | | | | | | | | | | | | | | | | |
| 9. abẹ | | | | | | | | | | | | | | | | | | |
| 10. ahọ́n | | | | | | | | | | | | | | | | | | |
| 11. ọ̀bọ | | | | | | | | | | | | | | | | | | |
| 12. ìgbálẹ̀ | | | | | | | | | | | | | | | | | | |
| 13. adájọ́ | | | | | | | | | | | | | | | | | | |
| 14. hanrun | | | | | | | | | | | | | | | | | | |
| 15. ìjókòó | | | | | | | | | | | | | | | | | | |
| 16. omi | | | | | | | | | | | | | | | | | | |
| 17. apá | | | | | | | | | | | | | | | | | | |
| 18. èkúté | | | | | | | | | | | | | | | | | | |
| 19. yàrá | | | | | | | | | | | | | | | | | | |
| 20. àdá | | | | | | | | | | | | | | | | | | |
| 21. oko | | | | | | | | | | | | | | | | | | |
| 22. apẹ̀rẹ̀ | | | | | | | | | | | | | | | | | | |
| 23. ìyàwó | | | | | | | | | | | | | | | | | | |
| 24. owó | | | | | | | | | | | | | | | | | | |
| 25. sùúrù | | | | | | | | | | | | | | | | | | |
| 26. agbègbè | | | | | | | | | | | | | | | | | | |
| 27. òwò | | | | | | | | | | | | | | | | | | |
| 28. ìnáwó | | | | | | | | | | | | | | | | | | |
| 29. àṣẹ | | | | | | | | | | | | | | | | | | |
| 30. ọ̀pọ̀lọpọ̀ | | | | | | | | | | | | | | | | | | |

 CC – 2011 The University of Texas at Austin

## SYLLABIC NASALS

Examples of the syllabic **/n/** can be found in the following:

| | | |
|---|---|---|
| Adéńrelé | a/dé/ń/re/lé | *name of a person* |
| dùǹdú | dù/ǹ/dú | *fried yam* |
| Bánkẹ́ | bá/n/kẹ́ | *a girl's name* |
| gbangba | gba/n/gba | *open arena* |
| kọ̀ǹkọ̀ | kọ̀/ǹ/kọ̀ | *toad* |
| gbàǹgbà | gbà/ǹ/gbà | *very big* |
| Déńdè | Dé/ń/dè | *name of a male person* |
| Bọ́láńlé | Bọ́/lá/ń/lé | *name of a person* |
| aláǹgbá | a/lá/ǹ/gbá | *lizard* |
| àǹkárá | à/ǹ/kà/rá | *a type of fabric* |
| àǹfààní | à/ǹ/fà/ní | *benefit* |

Examples of the syllable **/m/** can be found in the following:

| | | |
|---|---|---|
| Bímbọ́lá | Bí/m/bọ́/lá | *name of a person* |
| Bímpé | Bí/m/pé | *name of a boy or girl* |

| Proverb | |
|---|---|
| "Iyán l'oúnjẹ, ọkà l'oògùn,<br>Àìrí rárá là á j' ẹ̀kọ ,<br>K'ẹnu má dilẹ̀ ni ti gúgúrú." | *"Pounded yam is food,<br>Ọkà is medicine.<br>Solid pap is a last resort,<br>Popcorn is a snack.* |

 CC – 2011 The University of Texas at Austin

## Ìbàdàn

Ìbàdàn
Ìlú ẹ̀bá ọdan, olú ìpínlẹ̀ Ọ̀yọ́
Ìlú àwọn jagunjagun
Ìlú Lágelú àtOlúyọ̀lé
Ìlú Ìbíkúnlé òun Ògúnmọ́lá
Ogun kò kóbàdàn rí
Ìbàdàn ló kó gbogbo wọn yéye
Ìlú tó gbẹ àlejò, tó gbẹ oníle
Ìbàdàn ló fẹ̀ fẹ̀ fẹ̀
To kọjáa Mọ́níyà lọ́nà Ọ̀yọ́
Títí ó fi dé Ọmí Àdìó lọ́nà Abẹ́òkúta.
Onídùndú lọ́nà Ifẹ̀ àti Onígàǹbàrí lọ́nà Ìjẹ̀bú
Ìbàdàn, ìlú ológunlọ́gọ̀ òrùlé
Elérò ènìyàn bí eṣu yako
Bẹ́ ẹ débàdàn, ẹ bá mi kí wọn lọ́jà Òjé
Lọ́jàaba, Dùgbẹ̀  àt'Alẹ́ṣinlọ́yẹ́ oun Gbagi tuntun
Ní bi ti wọn ti ń ṣe kátàkárà
Tówó ti ń wọlé sápò ìṣòwò ní pẹrẹu
Olúbàdàn mo ṣe ọ́ ní kábíyèsí
Ọba ìlú Ìbàdàn, mo gbóṣú bàǹbà
Ìlú olókè púpọ̀ lẹ̀bá ọ̀dàn
Òkè Àdó, Òkèe Màpó, Òkè Ààrẹ
Òkèe Sééǹì, Òkèe Bọ́là, Òkèe Bíòkú
Òkè Ẹlẹ́yẹlẹ́, Òkèèbàdan!
Òkèèbàdan dákun gbè mí o
Bí o ti gbe ara iwájú o
Ẹni to fapá ṣe, fẹsẹ̀ ṣe nìbàdànán gbè
N ó ṣàṣekára ní tèmi.

By
Professor Adédọ̀tun Ògúndèjì
Dean, Faculty of Arts
University of Ibadan
Ibadan, Nigeria
June 2006